**NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA (NOUN)**

# YOR 316:
# INTRODUCTION TO THE CULTURE OF THE YORÙBÁ PEOPLE
# (ÌFÁÀRÀ SÍ ÀṢÀ ÀTI ÌṢẸ̀ṢE ÀWỌN YORÙBÁ)

*Láti ọwọ́*
**OLÚBÀYỌ̀ ỌLÁDIMÉJÌ ADÉKỌ́LÁ**
**B.A. Hons (Ifẹ̀), M.A, Ph.d (Ibadan)**

**INSTITUTE OF AFRICAN STUDIES**
**UNIVERSITY OF IBADAN**
**IBADAN, NIGERIA.**

**Course Content:** Introduction to the culture and introduction of the Yorùbá people

**Course Title and Description:** YOR 316: An introductory course on the culture and traditions which focuses on their traditional practices

**Course writer:** Dr. Olúbàyọ̀́ Ọládiméjì Adékọ́lá

**Course Editor:** Professor Adéṣọlá Ọlátẹ́jú

## ÀKÓÓNÚ KỌ́Ọ̀SÌ


Vice Chancellor's Message

Forward

Ìfáàrà sí kọ́ọ̀sì yìí

Àkóónú

**MÓDÙ KÌNNÍ** **1**

*Ìpín Kìnní: Àṣà àti Ìṣẹ̀ṣe Yorùbá* 1

Ìpín Kejì: *Ọdún Egúngún Ní Ìlu Ọlúpọ̀nnà* 13

*Ìpín Kẹta: Ọdún Òkèbàdàn Ní Ìlú Ìbàdàn* 18

*Ìpín Kẹrin: Ọdún Bẹẹrẹ Ní Ìlú Ọ̀yọ́* 24

*Ìpín Karùn-Ún: Orò Ìkẹ̀gbẹ́ Ní Ìlú Ìlá-Ọ̀ràngún* 29

**MÓDÙ KEJÌ** **34**

*Ìpín Kìnní: Àwọn Ẹ̀ka Àṣà Ìbílẹ̀ Ńláńlá Yorùbá* 34

*Ìpín Kejì: Ìwà Ọmọlúàbí* 44

*Ìpín Kẹta: Àṣà Ìbọ̀rìṣà Yorùbá I* 53

*Ìpín Kẹrin: Àṣà Ìbọ̀rìṣà Yorùbá II* 63

*Ìpín Karùn-Ún: Àṣà Ìgbéyàwó Láàrín Àwọn Yorùbá* 71

**MÓDÙ KẸTA: ÀWỌN ÀṢÀ YORÙBÁ KÉÉKÈÈKÉÉ**

Ìpín Kìnní: Ìtọ́jú Oyún, Ọmọ Bíbí Àti Ìtọ́jú Ọmọdé 78

Ìpín Kejì: Ìsọmọlórúkọ Àti Àwọn Orúkọ Ọmọ 85

Ìpín Kẹta: Àṣà Ìran-Ara-Ẹnilọ́wọ́ 94

Ìpín Kẹrin: Àṣà Oge Ṣíṣe 103

Ìpín Karùn-Ún: Àwọn Oúnjẹ Ilẹ̀ Yorùbá 112

**Ìfáàrà Sí Kọ̀ọ̀sì Yìí**

Módù mẹ́ta ni a pín kọ́ọ̀sì yìí sí, nígbà tí a pín módù kọ̀ọ̀kàn si ìpín márùn-ún.

Nínú modù kìn-ínní ni a ti ṣe àlàyé nîpa ìtumọ̀ àti ìbáṣepò tí ó wà láàrin àṣà àti ìṣẹ̀ṣẹ Yorùbá. Nínú ìpín kìn-ínní yìí ni a ti sọ̀rọ̀ nípa àṣà àti ìṣẹ̀ṣe Yorùbá àti àwọn àpẹẹrẹ díẹ̀ tí ó jẹ mọ́ èyí. A ṣe àlàyé pé àṣà jẹ́ ohun tí ó gbòorò púpọ̀, ti ó sì ní ẹ̀ka loríṣiríṣi, èyí tí a kò le mẹ́nubà nínú ìwé kan ṣoṣo.

A tọka ohun tí àṣà àti ìṣẹ̀ṣe dá lé lórí àti èrò àwọn ènìyàn lóríṣiríṣi lórí ohun tí a ń pè ní àṣà tàbí ìṣẹ̀ṣe Yorùbá. A wo àwọn tí a ń pè ní àwọn ènìyàn Yorùbá àti bí wọ́n ṣe gbilẹ̀ ní apá Ìwọ̀-Oòrùn orílẹ̀-èdè Nàìjíríà àti káàkírí ìlẹ̀ Ìwọ̀-Oòrùn ilẹ̀ Adúláwọ̀ àti ní gbogbo àgbáyé.

Nínú ìpín kejì ní a ti wo àṣà tàbí ìṣẹ̀ẹ̀ṣe tí ó rọ̀ mọ́ àwọn ọdún egúngún ní ìlú Olúpọ̀nnnà láti fi ṣe àpẹẹrẹ bí ìṣẹ̀ṣe náà ti kárí ilẹ̀ Yorùbá, nígbà tí ìpín kẹta ṣe àlàyé ọdún Òkèbàdàn ni ìlú Ìbàdàn, tí ìpín kẹrin sọ̀rọ̀ lórí ọdún Bẹẹrẹ ní ìlú Ọ̀yọ́ ní aye àtijọ́, bẹ̀ẹ̀ ni Ọrọ̀ ìkẹ̀gbẹ́ ní Ìlá –ọ̀ràngún ni a fi kásẹ̀ àlàyé wa nílẹ̀ nínú módù kìn-ínní.

Nínú módù kejì, a sọ̀rọ̀ nípa àwọn àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá, pàápàá iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé Yorùbá gẹ́gẹ́ bí iṣẹ àgbẹ̀, , ìṣẹ́ ọdẹ, iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ, iṣẹ́ ìṣègùn ìbílẹ̀ àti isẹ́ aṣọ híhun, ti wọ́n jẹ́ díẹ̀ nînú isẹ́ iṣẹ̀yìnbáyé Yorùbá.

Nínú ìpín kejì módù keji yìí ni a ti mẹ́nuba ìwà ọmọlúàbí ti a mọ àwọn Yorùbá mọ̀, a si wo àwọn àwòmọ́ ìwà ọmọlúàbí bíi ìkíni, ìbọ̀wọ̀-fún-àgbà, ìhùwàsí àti ìgbé-ayé rere àti iṣẹ́ ṣíṣe, bẹ́ẹ̀ ni a wo ipò ti àṣà ọmọlúàbí yìí wà lóde òní.

Nínú ìpín kẹta àti ẹ̀kẹrin ni a ti wo àṣà ìbọ̀rìṣa lẹ́lẹ́ka-ǹka, kí a tó ṣe àlàyé lórí àṣà ìgbéyàwó àti àwọn ìlànà tí ó jẹ́ mọ́ ọn lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́ nínú ìpín karùn-ún.

Nínú módù kẹta ẹ̀wẹ̀ , a sọ̀rọ̀ nípa ìtọ́jú oyún, ìsọmọlórúkọ àti orúkọ tí a ń sọ àwọn ọmọ wọ̀nyí. A kò sàìmẹ́nuba àṣà ìran-ara-ẹni-lọ́wọ́ àti oge ṣíṣe nínú módù yìí.

Ní ìparí, a wo àwọn oúnjẹ Yorùbá, a sì ṣe àlàyé lórí àwọn díẹ̀ pàtàkì nínú wọn. Wàyí o, a rí í pé àwọn iyípadà tí ń dé bá àwọn ẹ̀ka àṣà Yorùbá kan nítorí ọ̀làjú ìlẹ̀ òkèèrè tí ó wọlé wá.

**Àfojúsùn Kọ̀ọ̀sì Yìí**

Àfojúsùn kọ̀ọsì yìi ni láti jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ mọ̀ nípa àṣà ìbílẹ̀ àti ìṣẹ̀ṣe Yorùbá, èyí tí yóò le jẹ́ Kí wọ́n ni òye kíkún nipa ìṣẹ̀dálè àti àwọn nǹkan àjogúnbá ìran yìí.

Síwájú sí i, àkẹ́kọ̀ọ́ yóò le mọ̀ nípa bí àwọn nǹkan àjogúnbá kan ṣe wáyé àti àwọn ìyípadà tí ó ń dé bá àwọn nǹkan wọ̀nyí lóde òní.

Èyí nìkan kọ́, àkẹ́kọ̀ọ́ yòò le mọ ìdí abájọ tí àwọn Yorùbá ṣ máa ń gbé ìgbé ayé won pẹ̀lú àlàáfià, èyí tí ó ń mú ìdàgbasókè bá àwùjọ wọn. Bí akẹ́kọ̀ọ́ bá ní ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ àṣà àti ìṣẹ̀ṣe ìran Yorùbá , ìmọ̀ yìî yóò mú kí wọ́n le gbé àṣà abínibí wọn lárugẹ́ ní ìpéjọpọ̀ àgbáyé, wọ́n yóò sì le fi pàtakì àṣà àti iṣẹ̀ṣe wọn hàn gba-ngba ni àwùjọ yòówù tí wọ́n bá wà.

**Ojúṣe Akẹ́kọ̀ọ́**

Ojúṣe akẹ́kọ̀ọ́ ni kí ó fi ara balẹ̀ ka àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ wọ̀nyí yékéyéké láti ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìmọ̀ nípa àṣà abínibí Yorùbá. Lẹ́yìn tí akẹ́kọ̀ọ́ bá ti ka ìwé yìí ní ṣíṣẹ̀ntẹ̀lé tán, bí ó bá rí àwọn nǹkan kan tí ó ṣókùnkùn sí i, tàbí tí kò yé e dáradára, ó ní láti ṣe ìwádìí lọ́dọ̀ àwọn àgbà àti amòye nípa àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá tàbí kí ó bèèrè ìtọ́sọ́nà lọ́wọ́ olùkọ́ àṣà tí ó bá wà ní àrọ́wọ́tó rẹ̀.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé akẹ́kọ̀ọ́ kò le mọ̀ nípa gbogbo ẹ̀ka àṣà àti ìṣẹ̀ṣe Yorùbá tán nínú àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tàbí nínú ìwé kan ṣoṣo, ó gbọ́dọ̀ gbìyànjú láti máa ka àwọn ìwé tí a tọ́ka sí nípa rírà wọ́n tàbí ki ó lọ sí ilé ìyáwèé-kàwé tí ó bá wà nítòsí rẹ̀ fún ìdàgbàsókè nínú ìmọ̀ àṣà Yorùbá.

Akẹ́kọ̀ọ́ yẹ kí ó máa dá iṣẹ́ àmúrelé tí wọ́n bá fún un ṣe padà ní àsìkò tí ó yẹ àti pé ó ṣe pàtàkì kí akẹ́kọ̀ọ́ máa kópa nínú gbogbo ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí olùkọ́ bá pè wọ́n sí, àti pàápàá jùlọ nínú ìdánwò àṣekágbá tí ó bá wáyé.

**Ìgbéléwọ̀ tí Olùkọ́ yóò Máàkì (TMA)**

Ọ̀nà méjì ni a le pín ìgbéléwọ̀n yìí sí. Ọ̀nà kìn-ín-ni iṣẹ́ àmúṣe tí ó le jẹ́ ṣíṣe lójú ẹsẹ̀ tàbí tí ó le jẹ́ dídájọ́ sí, èyí tí akẹ́kọ̀ọ́ yóò mú relé tí wọn yóò sì ní ìpinnu láàrín àwọn olùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́ láti dá padà fún olùkọ́ rẹ̀ ní àkókò kan pàtó. Irú iṣẹ́ àmúrelé yìí yóò kó ìdá ọgbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún máàkì ní ìrètí pé ìmọ̀ tí akẹ́kọ̀ọ́ ni yóò wúlò fún un nínú iṣẹ́ àmúṣe àti ìdánwò lápapọ̀.

A ó ṣe àkíyèsí pé iṣẹ́ ṣíṣe wà ní ìparí ìpín kọ̀ọ̀kan, bẹ́ẹ̀ ni a ní ìrètí pé akẹ́kọ̀ọ́ yóò gbìyànjú láti wá ìdáhùn sí àwọn ìbèérè tí ó wà níbẹ̀. A ó gbìyànjú láti yẹ àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí wò, a ó sì fún akẹ́kọ̀ọ́ ní máàkì tí ó bá yẹ sí ìdáhùn mẹ́ta.

Iṣẹ́ àmúṣe àti ìgbéléwọ̀n yìí ni akẹ́kọ̀ọ́ yóò fi ránṣẹ́ papọ̀ sọwọ́ sí olùkọ rẹ̀ kí ọjọ́ ìdánwò tó pé, ṣùgbọ́n bí ìdí kan pàtàkì bá wà fún akẹ́kọ̀ọ́ láti má tètè dá iṣẹ́ náà padà ṣaájú ọjọ́ tí a fún un, irú akẹ́kọ̀ọ́ bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ fi ìdí tí ó fi rí bẹ́ẹ̀ tó olùkọ́ rẹ̀ létí, tí olùkọ́ náà yóò sì ṣe ohun tí ó bá yẹ.

**Ìdánwò Àṣekágbá àti Òṣùnwọ̀n**

Ìdánwò àṣekágbá fún kọ́ọ̀sí yìí (Ìfáàrà sí Àṣà àti Ìṣẹ̀ṣe Àwọn Yorùbá) yóò wáyé ní ọjọ́ tí àwọn Aláṣẹ Ilé-ẹ̀kọ́ àti Olùkọ́ bá fi ẹnu kò sí, èyí tí yóò jẹ jáde nínú àtẹ ìdánwò.

Láàrín wákàtí méjì ni akẹ́kọ̀ọ́ yóò dáhùn àwọn ìbéèrè tí a bá gbé síwájú rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ní ọgọ́ta máàkì (60%) ni a ó fi ṣe òdiwọ̀n rẹ̀.

Olùkọ́ le lo àsìkò tí ó bá wà láàrín ìparí kọ́ọ̀sì àti àkókò tí ìdánwò yóò bẹ̀rẹ̀ láti fi ṣe àtúnyẹ̀wò ẹ̀kọ́ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ rẹ̀.

Akẹ́kọ̀ọ́ tí kò bá ní í lè wá fún ìdánwò yìí nítorí ìdí pàtàkì kan tàbí òmíràn ní láti ni ẹ̀rí tó yanran-ntí, bẹ́ẹ̀ ni àwọn Aláṣẹ Ilé-Ẹ̀kọ́ ni yóò pinnu ohun àmúṣe lórí rẹ̀.

**Ìlànà Máàkì Gbígbà**

Máàkì gbígbà yóò dá  lórí bí akẹ́kọ̀ọ́ bá ṣe ṣe dáadáa sí nínú iṣẹ́ tí ó bá ṣe.

Àtẹ ìsàlẹ̀ yìí ń ṣe òdiwọ̀n máàkì gbígbà nínú kọ́ọ̀sì yìí.

| ÌGBÉLÉWỌ̀N | MÁÀKÌ |
|---|---|
| Iṣẹ́ àmúṣe 1-3<br>Mẹ́ta tó ba dára jù ni a ó ṣe àkọsílẹ̀ máàkì rẹ̀. | Ogójì (40%) |
| Ìdánwò àṣekágbá | Ọgọ́ta (60%) |
| Àròpọ̀ | Ọgọ́rùn-ún (100%). |

## MÓDÙ KÌNNÍ

### *Ìpín Kìnní: Àṣà àti Ìṣẹ̀ṣe Yorùbá*

***Àkóónú***

1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà/Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ìtumọ̀ Àṣà àti ohun tí Àṣà dá le lórí

4.2 Àwọn Yorùbá

4.3 Ìṣẹ̀ṣe Yorùbá

4.4 Ọdún Egúngún Ní Ilẹ̀ Yorùbá

4.5 Orò ṣíṣe láàrín Àwọn Yorùbá

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## MÓDÙ KÌNNÍ

### *Àṣà àti Ìṣẹ̀ṣe Yorùbá*

### 1.0 Ìfáàrà

Nínú Módù yìí ni a ti wo ohun tí a ń pè ní àṣà àti ìtumọ̀ tí a lè fún un ní gbogbogbòò tàbí ní gbogbo àwùjọ àgbáyé. A wo ohun tí àṣà tàbí ìṣẹ̀ṣe jẹ́ ní àwùjọ Yorùbá ní pàtàkì, bẹ́ẹ̀ ni a mẹ́nuba àwọn ẹ̀ka àṣà àti bí àwọn ẹ̀ka àṣà wọ̀nyí ṣe wà káàkiri gbogbo àgbáyé.

A jẹ́ kí á mọ̀ pé àṣà àti ìṣẹ̀ṣe súnmọ ara pẹ́kípẹ́kí dé bi pé ènìyàn lè fẹ́rẹ̀ má rí ìyàtọ̀ láàrin ohun tí a ń pè ní àṣà tàbí ìṣẹ̀ṣe Yorùbá. Níbi ni a ti kíyèsí pé ohun tí a ń pè ní àṣà tàbí ìṣẹ̀ṣe Yorùbá gbòòrò púpọ̀. Bí a ṣe ní àwọn ẹ̀ka àṣà tí ó gbòòrò ni a ní àwọn ẹ̀ka àṣà kéékèèké àti pé àyíká máa ń ṣe okùnfà fún àṣà nígbà mìíràn nígbà tí ìṣẹ̀ṣe máa ń mú wa rántí àwọn ohun tí ó ti ṣẹlẹ̀ kọjá láàrín àwùjọ kan, èyí tí ó jẹ́ mọ́nigbàgbé, tí ó sì ti lọ́ mọ́ àṣà irúfẹ́ àwùjọ bẹ́ẹ̀.

A kò sàì mẹ́nuba bí ìran Yorùbá ṣe jẹ́ àti bí wọ́n ṣe tànká sórí ilẹ̀ tí wọ́n wà lónìí.

### 2.0 Èròǹgbà/Àfojúsùn

Àwọn èròǹgbà tàbí àfojúsùn wa lórí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni:

- Kí akẹ́kọ̀ọ́ lè mọ ohun tí a ń pè ni àṣà tàbí ìtumọ̀ rẹ̀ lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́.
- Kí wọ́n lè mọ ìjọra àti ìyàtọ̀ tó wà láàrin àṣà àti ìṣẹ̀ṣe Yorùbá
- Kí wọ́n lè mọ ìdí abájọ tí àwọn Yorùbá fi ń tẹ̀lé àwọn ẹ̀ka àṣà tàbí ìṣẹ̀ṣe wọ̀nyí.
- Kí akẹ́kọ̀ọ́ lè ní ìmọ̀ nípa àṣà àti ìṣẹ̀ṣe àwùjọ tàbí agbegbe wọn yàtọ̀ sí tí agbègbè Yorùbá mìíràn tí ó yí wọn ká.
- Kí akẹ́kọ̀ọ́ lè ní ìrírí àyíká wọn dájú ṣáká

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

a) Kín ni àṣà túmọ̀ sí?

b) Sọ ìyàtọ̀ tàbí ìjọra tó wà láàrin àṣà àti ìṣẹ̀ṣe Yorùbá.

d) Ipa wo ni àyíká máa ń kó nínú àṣà àti ìṣẹ̀ṣe àwùjọ kọ̀ọ̀kan?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### *4.1 Kí ni Àṣà àti Ìṣẹ̀ṣe?*

Àṣà àti ìṣẹ̀ṣe jẹ́ ohun kan tí kò ṣe é fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú láàrín àwọn Yorùbá ní ayé àtijọ́ àti lóde òní pẹ̀lú nítorí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ohun tí a ti jẹ́ tàbí ohun tí a óò jẹ́ dá lórí ìmọ̀ tí a bá ní lórí àṣà abínibí wa. Èyí ni yóò fún wa ní òye lórí àwọn ohun tí a lè ṣe fún ìdàgbàsókè àwùjọ tí a wà. Nítorí náà, ó jẹ́ ohun tí a gbọ́dọ̀ mú ní ọ̀kúnkúndùn, bí a bá ń fẹ́ àlàáfíà àti ìlọsíwájú fún àwùjọ wa.

Onírúurú àwọn onímọ̀ àti àwọn omilẹgbẹ àwọn òǹkọ̀wé àti òǹpìtàn ló ti sọ̀rọ̀ lórí ohun tí àṣà tàbí ìṣẹ̀ṣe dá lé lórí tàbí fún un ní oríṣìíríṣìí ìtumọ̀ tàbí oríkì.

Àwọn mìíràn gbà pé ọ̀làjú ni àṣà jẹ mọ́, nítorí pé wọ́n rò pé ẹnikẹ́ni tí kò bá ní ìmọ̀ tàbí ẹ̀kọ́ nípa àyíká kò tíì mọ àṣà, nígbà tí àwọn mìíràn tilẹ̀ rò pé àwọn tí ìṣesí wọ́n bá jẹ mọ́ ìhùwàsí *'ará oko'* ni wọ́n mọ àṣà. A ó rí i pé èyí kò rí bẹ́ẹ̀ rárá.

Ọlájubù (1978:45) ṣe àlàyé pé àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá jẹ mọ́ ẹ̀sìn ìbílẹ̀, ìṣe tàbí ìgbé-ayé tó jẹ́ ti ìbílẹ̀ Yorùbá, nígbà tí Ládélé (1986:iv) ní tirẹ̀ fi yé wa pé kò sí ohun tí Yorùbá lè rò tàbí ṣe tí kò rọ̀ mọ́ àṣà, bẹ́ẹ̀ ni kò sí ìṣe kan tí kò bá àṣà lọ láàrín àwọn Yorùbá. Oyèwọlé (2002:21) ní tirẹ̀ sọ pé àṣà ní ó dàbí ìjánu ọkọ̀ fún àwùjọ. Fákóredé (n.d.: 6) náà rí àṣà gẹ́gẹ́ bí ohun tí ó jẹ mọ́ ìwà, ìṣesí tàbí ìhùwàsí tí ó ti di bárakú láàrin àwọn Yorùbá. O sọ àwọn àpẹẹrẹ bíi ìlànà àti ètò ìgbéyàwó, ìsìnkú, ogún pípín, ìkíni, ìsọmọlórúkọ, ìwọ̀fà yíyá, oyè jíjẹ, ìran-ara-ẹni-lọ́wọ́, òfin, ìkóbìnrinjọ, èèwọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Lára àwọn òǹkọ̀wé tó ti ṣe iṣẹ́ ìwádìí lórí àṣà àti ìṣẹ̀ṣe Yorùbá ni Ogúnbọ̀wálé (1966), Dáramọ́lá àti Jẹ́jẹ́ (1967), Ọlátúnjí (I970), Adéoyè (1979) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ní pàtó, a lè sọ pé àṣà Yorùbá ni ìgbàgbọ́, ìṣe, ìhùwàsí, ọgbọ́n, ìrírí, ìjìnlẹ̀ èdè, ìrònújinlẹ̀ àti àwọn nǹkan mìíràn tí ó mú kí á mọ ìgbòkègbodò àwọn ènìyàn yìí láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀rẹ̀. Nítorí náà, a lè fi àṣà wé ìjánu ọkọ̀, èyí tí ó ń ṣe atọ́kùn fún àwùjọ. Ṣùgbọ́n, lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìjíròrò àti àsọyé lórí ohun tí àṣà túmọ̀ sí, a ríi pé àṣà gbòòrò púpọ̀.

Nígbà tí Olódùmarè dá ẹ̀dá alàààyè sórí ilẹ̀ tán ní ìgbà ìwáṣẹ̀, ó dá àwọn kan sínú igbó kìjikìji, níbi tí igi ńláńlá pọ̀ sí jàǹtìrẹrẹ. Ẹlẹ́dàá yìí náà ló dá àwọn ẹ̀dá kan sínú ọ̀dàn níbi tí kò sí igbó púpọ̀, bẹ́ẹ̀ ni Ó dá àwọn kan sínú pápá tàbí aṣálẹ̀ níbi tí kò tilẹ̀ sí igbó tàbí ọ̀dàn kankan, tí gbogbo ilẹ̀ sì jẹ́ gbẹrẹfu.

Ìdí pàtàkì nìyí tí agbègbè tí a dá ènìyàn sí ṣe ní nǹkan án ṣe pẹ̀lú àṣà abínibí wọn. Elédùà fi àwọn kan sọjọ̀ sí etí omi ńlá bí òkun tàbí ọ̀sà nígbà tí òkè ńlá ràbàǹdẹ̀ ràbàǹdẹ̀ yí àwọn kan po.

Nítorí náà, nígbà tí ẹ̀dá ènìyàn wo àyíká rẹ̀ láti mọ ohun tí ó le ṣe é ní àǹfààní, ó ṣa èyí tí ó dára níbẹ̀, ó sì kẹ́yìn sí èyí tí ó le pa á lára, bẹ́ẹ̀ ni ohunkóhun tí ẹ̀dá agbègbè kọ̀ọ̀kan ṣà fún àǹfààní àti ìlọsíwájú àwùjọ rẹ̀ ni a lè pè ní àṣà. Bí àpẹẹrẹ, irú iṣẹ́ tí ènìyàn yóò ṣe dá lórí ohun tí ó wà ní àyìká rẹ̀, ìbáà ṣe àgbẹ̀, ọdẹ, ẹja pípa tàbí ohunkóhun tí ó lè ṣe láti mú kí ìgbé-ayé dẹrùn fún un. Ní pàtó, a lè pe àṣà ní ìhùwàsí, èdè, ìgbàgbọ́, iṣẹ́ ẹ̀mí tàbí ti ara èyí tí a mú lò nípa ìrírí àyíká tí a dá wa sí. Nítorí náà, a lè sọ pàtó pé ọ̀pọ̀ ìtàn àti àkọsílẹ̀ ló fihàn pé Afíríkà ayé àtijọ́ ní àṣà tí ó lajú, èyí kò sì yọ ilẹ̀ Yorùbá sílẹ̀.

## 4.1 Àwọn Yorùbá

Àwọn tí a máa ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí àwọn ẹ̀yà Yorùbá ní òde-òní ni àwọn ẹ̀yà tí ń sọ èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí èdè abínibí wọn. Lára wọn ni àwọn Ọ̀yọ́, Ẹ̀gbá, Yewa (Ẹ̀gbádò), Èkìtì, Ìjẹ̀bú, Ìjẹ̀ṣà, Oǹdó, Kétu, Ìgbómìnà, bẹ́ẹ̀ ni a lè rí àwọn wọ̀nyí ní ìlú bí i Ilé-Ifẹ̀, Ìbàdàn, Ọ̀yọ́, Èkó, Abẹ́òkúta, Oǹdó, Adó-Èkìtì, Ilá-Ọ̀ràngún, Àkúrẹ́, Ọ̀wọ̀ àti Àkókó. Àwọn mìíràn wà ní ìpínlẹ̀ Kwara, Kogí, Ẹdó, Delta àti Orílẹ̀-Èdè Olómìnira Benin. Bí a bá dé Ìlọrin àti ìlú tí ó yí i ká, ọmọ Yorùbá pọ̀ níbẹ̀ jàǹtìrẹrẹ ni. Nítorí náà, bí a bá sọ pé àwọn ẹ̀yà Yorùbá ni ó pọ̀ jù ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, a kò jẹ ayò pa. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé onírúurú ẹ̀ka èdè tàbí èdè àdúgbò ni a máa ń gbọ́ láààrín àwọn ẹ̀yà Yorùbá, kò sí ẹ̀yà Yorùbá tí kò le ka Bíbélì Yorùbá lóde òní. Àwọn ẹ̀ka èdè wọ̀nyí yàtọ̀ sí ara wọn

láti agbègbè kan sí èkejì bẹ́ẹ̀ ní èyí kò sọ pé kí wọ́n má gbọ́ ara wọn yé, níwọ̀n ìgbà tí wọ́n ti gbàgbọ́ pé ìran Odùwuwà ni àwọn íṣe.

## 4.3 Ìṣẹ̀ṣe Yorùbá

Bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa àṣà Yorùbá àti ìrírí àyíká wọn, a ní láti kíyèsí i pé ìṣẹ̀ṣe Yorùbá náà máa ń rìn pẹ́kípẹ́kí pẹ̀lú àṣà abínibí wọn ni. Bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìṣẹ̀ṣe Yorùbá, à ń sọ nípa orírun Yorùbá, ọgbọ́n, ìhùwàsí, ìrírí, ìjìnlẹ̀ èdè Yorùbá àti àwọn àbùdá pẹ̀lú ìṣesí tí a fi mọ àwọn ènìyàn yìí, èyí tí ó ti di bárakú, tí a sì fi mọ̀ wọ́n yàtọ̀ sí àwọn ènìyàn àwùjọ mìíràn (Oyèrìndé, et. al. 2016). Nítorí náà, ìṣẹ̀ṣe túmọ̀ sí àwọn nǹkan ìṣẹ̀yìn-báyé tí a ti ń ṣe fún ìdí kan tàbí òmíràn, tí a sì ti fi lọ́lẹ̀ ní ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ fún ìrántí lójọ́ iwájú.

Ìṣẹ̀ṣe yìí ni a lè tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí àwọn ohun tí Yorùbá máa ń ṣe láti fi ìdí àwọn ohun mánigbàgbé tí ó ti ṣẹlẹ̀ sí wọn ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ìṣẹ̀dálẹ̀ ìgbé-ayé wọn múlẹ̀, èyí tí wọ́n máa ń ṣe ìrántí rẹ̀ lóòrèkóòrè tàbí ní ọdọọdún. Bí àpẹẹrẹ, àwọn Yorùbá máa ń ṣe ọdún egúngún, èyí tí ó ṣúyọ nínú ìgbàgbọ́ wọn pé àwọn babańlá tàbí ìyá-ńlá wọn tó ti sùn sì máa ń wá láti bẹ̀ wọ́n wò fún àlàáfíà àwùjọ wọn.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ayẹyẹ ọdún egúngún gbalẹ̀ káàkiri tìbú tòòró ilẹ̀ Yorùbá, àwọn ìṣẹ̀ṣè mìíràn tún wà tí ó jẹ mọ́ àwọn àdúgbò kọ̀ọ̀kan. Àpẹẹrẹ àwọn wọ̀nyí ni ọdún Òkèbàdàn ní Ìlú Ìbàdàn, ọdún Agẹmọ ní agbègbè Ìjẹ̀bú, ọdún Orò àti Ṣàngó ní agbègbè Ọ̀yọ́, ọdún Edì ní Ilé-Ifẹ̀, Ìjẹ̀bú Rẹ́mọ, ọdún Ọ̀ṣun ní agbègbè Òṣogbo, ọdún Olúmọ ní agbègbè Abẹ́òkúta, pèlúpèlú ní ààrìn àwọn Èkìtì, ọdún Àsàbàri àti Olóógun ní Ìlú Ṣakí, ìyámọ̀pó ní Ìlú Ìgbẹ́tì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àwọn ìṣẹ̀ṣe wọ̀nyí máa ń mú kí wọn máa rántí ìṣẹ̀lẹ̀ mánigbàgbé èyí tí ó ti di bárakú fún wọn, bẹ́ẹ̀ ni èyí sì ti wọnú àṣà abínibí wọn. Bí a bá wo ohun tí a ń pè ní àṣà àti ìṣẹ̀ṣe yìí, a ó kíyèsí i pé wọ́n ti wọnú ara wọn débi pé a lè gbé wọn sí ara wọn nígbà mìíràn. Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, a lè tọ́ka sí àwọn ọdún wọ̀nyí, bí àpẹẹrẹ, ọdún egúngún tàbí ọdún orò, èyí tí ó jẹ mọ ẹ̀sìn àti ìgbàgbọ́ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí àṣà tàbí ìṣẹ̀ṣe Yorùbá. Nítorí náà, àṣà tàbí ìṣẹ̀ṣe Yorùbá lè jẹ mọ́ àwọn ìṣe Yorùbá èyí tí ó ti di bárakú fún wọn, tí wọ́n sì máa ń ṣe ìrántí láti ìrandéran títí di oní olónìí.

### *4.4 Ọdún Egúngún ní Ilẹ̀ Yorùbá*

Ayẹyẹ ọdún egúngún jẹ́ èyí tí ó gbajúgbajà láàrín àwọn Yorùbá láyé àtijọ́ àti lóde òní. Àkókò ìgbà òjò ni wọ́n sábà máa ń ṣe ọdún egúngún. Ọdún yìí ṣùyọ nínú ìgbàgbọ́ Yorùbá pé àwọn aláṣekù tàbí àwọn ìbọ, èyí ni àwọn babańlá wọn tó ti kú, ṣùgbọ́n tí kì í jìnnà sí wọn láti máa bẹ̀ wọ́n wò, kí wọ́n sì máa wúre fún wọn nígbà gbogbo. Èyí ní o fà á tí wọ́n fi ya àkókò kan sọ́tọ̀ láti máa ṣe ìrántí wọn, kí wọ́n sì gbà wọ́n ní àlejò.

Gẹ́gẹ́ bí Ìdòwú (1962) àti Awólàlú (1979) ti sọ, àwọn Yorùbá ní ìgbàgbọ́ nínú Olódùmarè, ṣùgbọ́n onírúurú ọ̀nà ni wọ́n ń gbà jẹ́ kí ìgbe àti ẹ̀bẹ̀ wọn dé ọ̀dọ̀ Rẹ̀. Nítorí náà, ọ̀kan lára àwọn ọ̀nà tí àwọn Yorùbá ń gbà sin Olódùmarè yìí ni bíbọ egúngún gẹ́gẹ́ bí àlejò wọn láti ọ̀run. Ìdí yìí náà ni wọ́n fi ń pe àwọn egúngún ní *"ará ọrun kìn-ìn-kan"*.

Kò sí ẹ̀yà Yorùbá tí kì í ṣe ayẹyẹ ọdún egúngún bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àkókò tí wọ́n máa ń ṣe é lè yàtọ̀ láti agbègbè kan sí èkejì tàbí láti ìlú kan sí òmíràn.

Nínú ìlú kọ̀ọ̀kan, ìdílé tàbí agbo-ilé kọ̀ọ̀kan ló máa ń ní egúngún tiwọn èyí tí yóò ní orúkọ tirẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, ní ìlú Ìbàdàn, wọ́n ní àwọn egúngún bíi Atìpàkọ́, Alápáńṣánpá, Eégún Ọdẹ, Ìpọ́nríkú, Afìdíẹlẹ́gẹ̀ẹ́, Gbódógbodò, Olóòlù àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ní àwọn ìlú Ẹ̀gbá ni a ti máa ń rí àwọn egúngún bí Gẹ̀lẹ̀dẹ́, Awúrú àti Ìjẹ̀pà, bẹ́ẹ̀ ni àwọn egúngún bí i Òkòtòròjò, Akọ Egúngún, Eégún Adó ni ó máa ń jáde ní agbègbè Èkìtì. Ní agbègbè Èkó àti Àwórì ẹ̀wẹ̀, a máa ń rí Ẹ̀yọ̀. Àwọn egúngún kan wà ní agbègbè Ọ̀yọ́ tí a ń pè ní Ẹlẹ́wẹ, Ajófóyìnbó, egúngún Ajóbíewé. Àwọn egúngún wọ̀nyí máa ń jó káàkiri ìlú Ọ̀yọ́ àti agbègbè rẹ̀. Àwọn egúngún kan wà ní ilẹ̀ Tápà tí a ń pè ní Ìgunnu. Ìdí nìyí tí a fí máa ń kọ ọ́ lórín pé:

> Ìgunnu ló ni Tápà
> Tápà ló nìgunnu
> Ẹ máa kówó wa ná.

Yàtọ̀ sí àwọn wọ̀nyí, a tún máa ń gbọ́ nípa àwọn Egúngún Alárìnjó tàbí Egúngún Pidánpidán. Àwọn wọ̀nyí máa ń pa idán oríṣiríṣi láti dá àwọn ènìyàn lárayá.

Wọ́n sábà máa ń lọ láti agbègbè kan sí ekejì láti ṣeré fún àwọn olùwòran wọn. Àpẹẹrẹ àwọn egúngún wọ̀nyí ni egúngún Àjàǹgìla àti egúngún Ayélabọ́lá.

Bí àwọn eléégún bá fẹ́ mú egúngún jáde, wọn yóò wá ẹnìkan nínú ẹbí tí ó jọ bàbá tó ti kú, tí wọn yóò wọ̀ ọ́ ní ẹ̀kú tàbí agọ̀, èyí ni aṣọ tí yóò bo gbogbo ara ẹni náà yàtọ̀ sí ojú nìkan tí wọn yóò fi sílẹ̀. Egúngún yìí yóò máa yíde káàkiri ìlú tàbí agbègbè, yóò sì máa wúre fún tọmọdé tàgbà, lọ́kùnrin àti lóbìnrin pẹ̀lú àṣẹ pé òun yóò máa rí wọn ní ọdọọdún. Pẹ̀lú ìlù àti ìfọn ni àwọn ẹbí àti ará, lọ́kùnrin àti lóbìnrin yóò máa jó, tí wọn yóò sì máa wólẹ̀ níwájú ará ọ̀run yìí láti gba ìre lẹ́nu wọn.

Bí àwọn egúngún wọ̀nyí bá ti jáde, wọn yóò jó lọ sí ilé àwọn Ọba, Báálẹ̀ àti Ìjòyè Ìlú láti súre fún wọn, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò máa wúre fún àwọn ènìyàn ìlú pẹ̀lú. Ọba àti àwọn ìjòyè ìlú yóò máa ta wọn lọ́rẹ owó, aṣọ, ohun jíjẹ, mímu àti àwọn ẹ̀bùn pàtàkì mìíràn.

A kò gbọdọ̀ gbàgbé láti sọ fún wa pé àwọn egúngún wọ̀nyí máa ń ní atọ́kùn tí yóò máa darí wọn níbikibi tí wọn bá ń lọ fún ìdí kan tàbí òmíràn.

Olórí àwọn Abọrẹ̀ eégún ni a mọ̀ sí *__Alágbààà__*. Alágbààà ni ìtàn sọ pé ìran yìí ni ó kọ́kọ́ dá egúngún bíbọ sílẹ̀ tí wọ́n sì gbàgbọ́ pé àwọn babańlá àti ìyáńlá wa tí ó ti lọ sí ọ̀run ni, kì í ṣe pé wọ́n kú àkúrun. Nípa bẹ́ẹ̀, wọ́n gbàgbọ́ pé àwọn babańlá àti àwọn ìyáńlá wọ̀nyìí máa ń ṣe ìbẹ̀wò sí ìdílé wọn lórèkóòrè láti wúre fún wọn. Alágbààà ni olórí àti aláṣẹ fún gbogbo egúngún, òmi ni ó sì máa ń ṣe ètùtù tí ó jẹ mọ́ ọdún yìí. Òun ni ó máa ń dájọ́ tí ọdún egúngún yóò bẹ̀rẹ̀, lẹ́yìn ìgbà tí òun àti àwọn abọrẹ̀ yòókù bá ti fikùnlukùn tí wọ́n sì bèèrè lọ́wọ́ Ifá. Ifá ni yóò sọ bí ọjọ́ mẹ́tàlá, mẹ́ẹ̀ẹ́dógún tàbí ọjọ́ mẹ́tàdínlógún ni kí wọ́n kéde, wọn yóò sì lu agogo káàkiri ìlú lẹ́yìn náà.

Lẹ́yìn tí wọ́n bá dájọ́ tán, ìpalẹ̀mọ́ yóò bẹ̀rẹ̀ pẹrẹu, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò ṣe àìsùn nígbà tí ọjọ́ egúngún bá ku ọ̀la. Bí wọn ti ń sè, ni wọn yóò máa sọ̀. Àwọn ìdílé kọ̀ọ̀kan yóò máa pa ẹran tàbí ohun ọ̀sìn mìíràn bọ àwọn bàbá àti ìyá wọn tó ti papòdà.

Bí wọ́n ṣe ń ro àmàlà ni wọn yóò máa ṣùkọ, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò máa ṣu ọ̀lẹ̀lẹ̀ fún eégún. Ìdí nìyí tí a fi máa ń gbọ́ pé *'Wọ́n ń kúnlẹ̀ ọdún eégún'*.

Ní ọjọ́ kẹta ẹ̀wẹ̀, àwọn ọmọdé ní ìdílé eléégún náà yóò to àwọn ègé aṣọ kéékèèké jọ, wọn yóò sì ta á mọ́ra láti gbé eégún tiwọn náà. Irúfẹ́ àwọn eégún ọmọdé báyìí ni a ń pè ní Tòm̀bòlò, tí wọn yóò máa kọrin, wọn yóò sì máa jo láti gbowó kiri ní àdúgbò. Àwọn Tòm̀bòlò yìí ni àwọn ọmọdé tí ó ti kú láìpé ọjọ́ tí àwọn náà tún padà wá bẹ ilé wò láti kí àwọn ẹlẹ́gbẹ́ wọn kú àtijọ́. A sábà máa ń ki àwọn Tòm̀bòlò wọ̀nyí pé:

Tòm̀bòlò bólobòlo
Ajọ̀lẹ̀lẹ̀ má lè sáré,
Eégún ará oko.

Àkókò ọdún yìí ni a lè pín sí ọ̀nà mẹ́ta- Ìta, Ìje àti Ìtàdógún. Ní ọjọ́ Ìta yìí, àríyá yóò pọ̀ rẹpẹtẹ, bẹ́ẹ̀ ni àkókò yìí ni àwọn Tòm̀bòlò yìí máa ń jáde káàkiri. Ní ọjọ́ Ìje ẹ̀wẹ̀, àwọn egúngún ńlá yóò jáde, wọn yóò kí gbogbo àdúgbò pàápàá jùlọ, àwọn tí wọ́n dáná ọdún lọ sí ìgbàlẹ̀. Lẹ́yìn èyí ni àwọn egúngún wọ̀nyí yóò lọ jó fọ́ba àti ìjòyè. Lẹ́yìn Ìje yìí ẹ̀wẹ̀, àwọn eégún abàmì ni yóò máa jáde títí yóò fi di Ìtàdógún tí ayẹyẹ ọdún egúngún yóò kásẹ̀ nílẹ̀, tí irúfẹ́ ayẹyẹ bẹ́ẹ̀ yóò tún di ọdún tí ó tẹ̀lé e.

### *4.5 Orò Ṣíṣe Láàrín Àwọn Yorùbá*

Ọ̀kan lára àwọn ìṣẹ̀ṣe pàtàkì Yorùbá ni orò jẹ́. Ìtàn àtẹnudẹ́nu kan sọ pé ọmọ ìyá àti bàbá kan ni Orò àti Egúngún jẹ́ ní ìgbà ìwásẹ̀. Wọ́n lọ sí ẹ̀yìn odi láti wá ọrọ̀-ajé tí yóò mú ìgbé-ayé wọn rú gọ́gọ́ sí i. Nígbà tí wọ́n dé ìlú tí wọ́n lọ, egúngún ní tirẹ̀ ń ṣe iṣẹ́ aṣekára ṣùgbọ́n Orò ko tẹpa mọ́ṣẹ́. Nígbà tí ó tó àsìkò láti padà lọ sílé, Egúngún kó ọ̀pọ̀lọpọ̀ owó, aṣọ, ẹrú àti ẹrù wálé, bẹ́ẹ̀ ni Orò kò rí nǹkan kójọ. Aṣọ àkìsà ni aṣọ rẹ̀; èyí ni o sì mú un láti takú sí ìrìn-àjò náà. Ṣùgbọ́n nígbà tí Egúngún àti àwọn ènìyàn lọ fi agbára mú Orò láti padà wálé, wọn kò fẹ́ fi àṣírí rẹ̀ hàn síta, pàápàá jùlọ fún àwọn obìnrin. Ní ààrín ọ̀gànjọ́ ni wọ́n mú un dé, tí wọ́n sì ṣe é léèwọ̀ fún àwọn obìnrin láti fi ojú kàn án. Orò yìí jẹ mọ́ awo Yorùbá kan tí a kò fihàn sí obìnrin títí di òní olónìí. Ìdí nìyí tí a ṣe máa ń gbọ́ nínú orin àti ọ̀rọ̀ Yorùbá kan pé;

Awo egúngún lobìnrin lè ṣe
Awo gẹ̀lẹ̀dẹ́ lobìnrin lè mọ̀
Bóbìnrin bá fojú korò
Orò yóó gbé e.

Yàtọ̀ sí pé obìnrin kò gbọdọ̀ dé ibi orò, awo orò jẹ́ ìṣẹ̀ṣe tí ó sábà máa ń hàn sí àwọn ọ̀tọ̀kùlú ìlú àti àwọn lóókọ-lóókọ àwùjọ.

Orò ṣe pàtàkì púpọ̀ láàrín àwọn Ọ̀yọ́, àwọn ẹ̀yà Ẹ̀gbá àti àwọn Àwórì. Wọ́n máa ń bọ orò ní ààrin àwọn Ìjẹ̀bú pàápàá, wọ́n gbà pé òrìṣà ará ọ̀run ni orò í ṣe. Ìdí nìyí tí wọn fi máa ń lọ pàdé ẹ̀mí ẹni tí ó bá kú náà níbi tí wọ́n bá ṣètò rẹ̀ sí, ìbáà ṣe nínú agbo ọ̀gẹ̀dẹ̀, létí odò, níbì agọ̀ igi ńlá tàbí ní oríta.

Yorùbá gbàgbọ́ pé a kò lè rí ojú orò nítorí pé ará ọ̀run ní í ṣe. Bóyá ìdí nìyí tí Orò kìí ṣe é jáde lọ́sàn-án àfi lòru ọ̀gànjọ́.

Gẹ́gẹ́ bí ìtàn àtẹnudétí ṣe sọ, àwọn Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú ni wọ́n máa ń lo Orò láti gba agbára ńlá ní ayé àtijọ́, bẹ́ẹ̀ ni inú igbó ni ojúbọ Orò sábà máa ń wà, bẹ́ẹ̀ ni kò sí ẹni tí ó le wọ igbó Orò lọ, bí kò ṣe àwọn àwòrò rẹ̀.

Nígbàkígbà tí wọ́n bá fẹ́ bẹ Orò nísẹ́, àwọn àwòrò rẹ̀ ni yóò mú un jáde láti inú igbó ìgbàlẹ̀ wá sí àárín ìlú, bẹ́ẹ̀ ni obìnrin kò gbọdọ̀ fi ojú kàn án. Yàtọ̀ sí èyí, àwọn ọkùnrin tí kò bá mọ Orò yóò farasin pẹ̀lú nítorí pé awo tí ń bẹ láàárín olórò kò fún ọ̀pọ̀ àwọn ọkùnrin náà ní àǹfààní láti mọ̀ ojúbọ rẹ̀. Àwọn wọ̀nyí ni ọ̀gbẹ̀rì tí kò lè mọ awo Orò.

Ní ayé àtijọ́, àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Òṣùgbó ni ó máa ń jẹ aṣáájú níbi orò, ìdí nìyí tí wọ́n ṣe ní agbára púpọ̀ ní ìlú, pàápàá jù lọ ní ìlú Abẹ́òkúta àti agbègbè rẹ̀. Nínú ẹgbẹ́ Òṣùgbó yìí ni a ti gbọ́ pé ẹgbẹ́ Ògbóni ti ṣùyọ láàrín àwọn Ẹ̀gbá. Ìdí nìyí tí àwọn Òṣùgbó ṣe máa ń ṣe àjọ̀dún Orò tìlù tìfọn.

A gbọ́ pé bíbú ni Orò máa ń bú, bẹ́ẹ̀ ni nígbàkigbà tí ó bá bú báyìí, ẹ̀rù jẹ̀jẹ̀ ni bíbú yìí fún àwọn obìnrin àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọkùnrin pẹ̀lú, pàápàá nígbà tí Orò bá ń bọ̀ wá sí àárín ìlú tàbí tí àwọn àwòrò rẹ̀ bá fẹ́ ṣe ètùtù rẹ̀ ní igbórò (Igbó Orò).

Ní ayé ìgbàanì, Orò ni wọ́n fi máa ń dájọ́ fún àwọn ọ̀daràn, wọ́n lè dájọ́ ikú fún ẹlẹ́sẹ̀ bẹ́ẹ̀ tàbí kí wọ́n lé e kúrò nínú ìlú, wọ́n sì lè ta á lójì. Bí wọ́n bá ń ṣe àjọ̀dún Orò yìí, ìlú ijó, orin àti onírúurú ohùn ìdárayá ni ó máa ń wáyé, ó sì máa ń jẹ́ àkókò ayọ̀ fún àwọn olùsìn rẹ̀.

Gẹ́gẹ́ bí i tí ọdún egúngún Olóòlù ní ilẹ̀ Ìbàdàn, ẹnikẹni kò gbọdọ̀ yọjú wo Orò àti pé ẹni tí ó bá dẹ́jàá yìí, Orò yóò gbé e, pàápàá jù lọ, àwọn ọ̀gbẹ̀rì.

Inú igbó Orò ni Orò tí máa ń jẹun kí ó tó jáde, bẹ́ẹ̀ ni Orò kò gbọdọ̀ jẹ oúnjẹ rẹ̀ kù kí ó máa bàa fa ìpalára fún àwọn atọ́kùn rẹ̀ àti àwọn ènìyàn ìlú mìíràn. Ìdí nìyí tí a fi máa ń gbọ́ pé *'A kìí rí àjẹkù Orò'*, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn kan sọ pé ohunkóhun tí Orò bá ti jẹ kù, wọ́n máa ń bò ó mọ́lẹ̀ ni.

Lóde òní, a gbọ́ pé wọ́n sì máa ń ṣe àjọ̀dún Orò ní ilẹ̀ Yorùbá, ní pàtàkì jù lọ ní agbègbè Ìjẹ̀bú, Ẹ̀gbá, Àwórì àti Ìlú Ọ̀yọ́, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń bọ òrìṣà tí ó fara jọ Orò ní agbègbè Èkìtì, èyí tí wọn ń pè ní Ọlúa, Àtogùn tàbí Ẹ̀rẹ̀jù.

Ìdílé àti ìlú kọ̀ọ̀kan ló ní ìṣẹ̀ṣe tirẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, ìṣẹ̀ṣe àwọn ìbàdàn ni *Òkèbàdàn*, ti àwọn Ẹ̀gbá ni *Olúmọ, Àsabàrí* àti *Olóógun* ni ti Ṣakí nígbà tí ìṣẹ̀ṣe àwọn Ìdèrè ni *Ayé* àti *Òkèdèrè.* Ní agbègbè Ayétẹ̀ ni wọ́n ti ń bọ *Ìsámíni,* nígbà tí àwọn ènìyàn Ìgàngàn máa ń bọ *Ààke.*

Àwọn ènìyàn tilẹ̀ máa ń fi oríkì ìṣẹ̀ṣe ki àwọn ọmọ wọn. Bí àpẹẹrẹ, wọn lè ki àwọn ọmọ ìbílẹ̀ Ṣakí báyìí pé:

Pẹ̀lẹ́ o,
Ọmọ Ọ̀kẹ̀rẹ̀
Ọmọ Àsabàrí
Ọmọlójú Olóógun
Ọmọ Àsabàrí kìí kọ̀jà
Olóógun ò kọ eré
Bọ́rọ̀ bá dọ̀rọ̀ ìjà,
Ẹ ránṣẹ́ p'Àsabàrí
Bó bá dọjọ́ eré
Ẹ ránṣẹ́ p'Olóógun….

Bí ó bá ṣe ọmọ Ìdèrè ni, wọ́n lè máa kìí pé;

Pẹ̀lẹ́ o,
Ìdèrè má dè
Ọmọ ọlọ́gbun àyíkú
Ọmọ Ayé logún
Ọmọ Òkèdèrè lọgbọ̀n
Ọmọ Ayé pa mí kí n kú dandan
Òkèdèrè dákun gbà mí là….

Ní ti àwọn ọmọ Ìṣẹ́yìn, wọ́n máa ń kì wọ́n pé;

> Pẹ̀lẹ́ o,
> Ìṣẹ́yìn Orò
> Ọmọ Ẹbẹdí mọkọ
> Ọmọ Ọ̀gbààrà
> Tó la ilé Ìṣẹ́yìn já…..

Ìdílé kọ̀ọ̀kan ló ní agbára tirẹ̀ yàtọ̀ sí ti ìlú lápapọ̀, bẹ́ẹ̀ ni, bí wọ́n bá súre fún ẹnikẹ́ni nínú àwọn ọmọ ìdílé náà lórúkọ ìṣẹ̀ṣe ìdílé wọn, èyí yóò ṣẹ mọ́ wọn lára.

Kì í ṣe láti dáàbò bo ìdílè tàbí ìlú nìkan ni ìṣẹ̀ṣe wà fún, ìṣẹ̀ṣe tún máa ń jà fún àwọn ará ìlú tàbí ìdílé tí ó ni ín. Èyí nìkan kọ́, wọ́n tún máa ń lo ìṣẹ̀ṣe bí a ṣe máa ń lo agbára ọfọ̀, àyájọ́ tàbí ògèdè. Bí ẹnikẹ́ni bá ní ìṣòro kan, tí irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ sì fí òtítọ́ inú ké pe ìṣẹ̀ṣe ìdílé wọn, kíákíá ni òkè ìṣòro onítọ̀hún yóò di pẹ̀tẹ́lẹ̀.

Ọdọọdún ni wọ́n sábà máa ń ṣe ètùtù tàbí ìrúbọ sí ìṣẹ̀ṣe níbi tí gbogbo ọmọ ìdílé tàbí ìlú tí ọ̀rọ̀ náà bá kàn yóò pésẹ̀, kí wọ́n sì ṣe ojúṣe wọn ní àkókò náà, bẹ́ẹ̀ ni ẹnikẹ́ni tí ó bá kọtí ikún sí ojúṣe rẹ̀ ní àkókò yìí le fi túláàsì ṣe é nígbà tí ìṣẹ̀ṣe bá kó onítọ̀un sí wàhálà.

Agbára ìṣẹ̀ṣe jẹ́ agbára tí àwọn Yorùbá máa ń lò fún ìdáàbòbo ara wọn, ìrànlọ́wọ́ àti ìtẹ̀síwájú àwọn ará ìlú tàbí ìdílé tí ó ni ín; bẹ́ẹ̀ ni wọn kìí lò ó sí ọ̀nà burúkú tàbí ohun ìpalára kankan àyàfi bí wọ́n bá fẹ́ fi bá ọ̀tá jà láti dáàbò bo ara wọn.

Láyé ìgbàanì, ìṣẹ̀ṣe wúlò púpọ̀, ṣùgbọ́n ó ṣeni láàánú pé nígbà ti ẹ̀sìn òkèèrè wọ̀lú wá, àwọn ènìyàn kan kọ ìṣẹ̀ṣe sílẹ̀. Ṣùgbọ́n ṣá o, àwọn kan kò kọ̀ ọ́ sílẹ̀ pátápátá, ṣùgbọ́n wọ́n ń ṣe ojúṣe wọn. Ìdí nìyí tí a fi máa ń gbọ́ orin nígbà náà pé;

> Àwa ó ṣorò ilé wa o,
> Àwa ó ṣorò ilé wa o
> Ẹ̀sìn kan kò pé é, ó e
> Ẹ̀sìn kan kò pé káwa má ṣorò
> Àwa ó ṣorò ilé wa o

Ṣùgbọ́n lóde òní, èké ti dáyé, aásàà ti d'Ápòmù. Ọ̀pọ̀ àwọn ọmọ Yorùbá ló ti kọ̀yìn sí àṣà àti ìṣẹ̀ṣe baba-ńlá wọn, nítorí àwọn ẹ̀sìn ìgbàlódé tó gbòde kan. Wọ́n tilẹ̀ gbàgbé pé ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn kò papọ̀ mọ́ àṣà abínibí àti ìṣẹ̀ṣe wa. Nítorí àìnáání tàbí àìkọbi ara

sí àṣà àdáyébá àti ìṣẹ̀ṣe, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn nǹkan burúkú bùrùjà tí kìí ṣẹlẹ̀ tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀ nínú ìdílé tàbí ìlú ni ó ń ṣẹlẹ̀ báyìí, tí wọ́n sì ń sọ pé 'iṣẹ́ èṣù ni' tàbí pé 'àmúwá Ọlọ́run' ni.

## 5.0 Ìṣonísọ́kí

Nínú ìpín yìí ni a ti sọ̀rọ̀ nípa ohun tí àṣà àti ìṣẹ̀ṣe Yorùbá jẹ́. A wo àwọn ìtumọ̀ tí wọ́n fún àṣà àti bí àṣà àti ìṣẹ̀ṣe ṣe máa ń jẹ́ kí àwùjọ tẹ̀síwájú.

A sọ bí àyíká wa ṣe nípa tí ó kó nínú àṣà àti bí ìṣẹ̀ṣe ṣe jẹ́ nǹkan mọ́nigbàgbé fún ìlú àti ìdílé Yorùbá. A sọ̀rọ̀ nípa àwọn Yorùbá àti orírun wọn, bẹ́ẹ̀ ni a ṣe àlàyé nípa ọdún méjì tí ó gbajúgbajà láàrín àwọn Yorùbá láyé àtijọ àti lóde òní, èyí ni ọdún egúngún àti ọdún orò.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Kín ni àṣà àti ìṣẹ̀ṣe Yorùbá jẹ́?

2. Ǹjẹ́ ìyàtọ̀ wà láàrín àṣà àti ìṣẹ̀ṣe Yorùbá?

3. Sọ àpẹẹrẹ márùn-ún ohun tí a lè pè ní àṣà Yorùbá.

4. Kín ni ọdún egúngún dá lé lórí láàrín àwọn Yorùbá?

5. Kín ni a ń pè ní orò, àti pé níbo ni orò bíbọ wọ́pọ̀ sí láàrín àwọn Yorùbá?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Olúdáre Ọlájubù (ed) (1978). *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*, Lagos, Longman Nig. Ltd.

Fakorede, O. (n.d.). *Kristiani àti Àṣà Pẹ̀lú Ọ̀rìṣà Ìbílẹ̀.* Okeho, Tunde Akinọshọ Commercial Press.

Oyèwọlé, B. (2002). 'Titẹpẹlẹ mọ́ Àṣà àti Ìṣe Ilẹ̀ Òkèèrè' *Yorùbá Gbòde: Ìwé Àtìgbàdégbà Ẹgbẹ́ Akọ́mọlédè àti Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn, Macmillan Nig. Plc., Vol. 3, Nọ 2, o.i. 18-24.

Ládélé, T.A. *et.al* (1986). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn, Macmillan Nig. Publishers Ltd.

Ìdòwú, O. (1962). Olódùmarè, God in Yorùbá Belief.

Awólalù, J.O. àti Dọ̀pámú, P.A. (1979). *West African Traditional Religion*. Ìbàdàn, Oníbọn-Oje Press and Book Industries Limited.

## MÓDÙ KÌNNÍ

### Ìpín Kejì: *Ọdún Egúngún Ní Ìlu Ọlúpọ̀nnà*

*Àkóónú*

1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ọdún Egúngún Ní Ìlú Olúpọ̀nnà

4.2 Ètò fún Ayẹyẹ Ọdún Egúngún Ní Ìlú Olúpọ̀nnà

4.3 Ìpalẹ̀mọ́ fún ọdún Egúngún ní Ìlú Olúpọ̀nnà

4.4 Àkókò Ayẹyẹ Ọdún Ní Ìlú Olúpọ̀nnà

4.5 Ìkáṣẹ̀ Ọdún Egúngún Ní Ìlú Olúpọ̀nnà

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Ní ìpín yìí ni àti fi ìṣẹ̀ṣe Yorùbá hàn ní àwọn ìlú kan ní agbègbè Ọ̀yọ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé káàkiri ilẹ̀ Yorùbá ni a ti máa ń ṣe ọdún egúngún, bí wọ́n ṣe ń ṣe é yàtọ̀ láti ìlú tàbí agbègbè kan sí òmíràn. Ìdí nìyí tí a fi wo àwọn àpẹẹrẹ egúngún ṣíṣe ní ìlú Olúpọ̀nnà. A wo ìgbàgbọ́ tí àwọn Yorùbá ní nípa ìyè lẹ́yìn ikú àti pé wọ́n gbàgbọ́ pé àwọn òkú tún máa ń padà wá bẹ̀ wọ́n wò lọ́ọdọọdún lẹ́yìn tí baba tàbí ìyá bẹ́ẹ̀ bá ti pa ipò dà.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Ní ìparí ẹ̀kọ́ yìí, èròǹgbà wa ni kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti àwọn òǹkàwé yìí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìmọ̀ nípa:

- Ọdún egúngún ní àwọn ìlú kan.
- Bí wọ́n ṣe máa ń ṣe ọdún egúngún ní àgbègbè wọn.
- Ìdí tí wọ́n ṣe máa ń ṣe àwọn ọdún wọ̀nyí
- Ọdún ìṣẹ̀ṣe tí ó máa ń wáyé àti ìdí tí wọn fi ń ṣe wọ́n.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣááju

- Níbo ni ìlú Olúpọ̀nnà wà ní ilẹ̀ Yorùbá?
- Níbo ni a ti lè rí àwọn ìlú mìíràn tí a dárúkọ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí?
- Sọ nípa ọdún ìbílẹ̀ kan tí ó gbajúgbajà ní ìlú rẹ.

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́: *Ọdún Egúngún Ní Ìlú Olùpọ̀nnà*

### *4.1 Ìlú Olúpọ̀nnà àti Agbègbè Rẹ̀*

Ìlú Olúpọ̀nnà jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ìlú olókìkì ní ilẹ̀ Yorùbá. Ìlú yìí wà nítòsí ìlú Ìwó ní ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun.

Bí a ti mọ̀ síwájú pé egúngún bíbọ jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àṣà abínibí Yorùbá, a rí i pé àṣà egúngún bíbọ yìí jẹ́ àṣà tí ó gbajúgbajà láàárín àwọn Yorùbá títí di òní olónìí.

Ọdún egúngún yìí ṣúyọ nínú ìgbàgbọ́ Yorùbá pé àjíǹde wà lẹ́yìn ikú àti pé àwọn ìbọ tàbí àwọn babańlá wọn kì í fi wọ́n sílẹ̀ lẹ́yìn tí wọ́n bá ti pa ìpò dà. Wọ́n gbàgbọ́ pé àwọn babańlá wọn yìí máa ń wá láti bẹ̀ wọ́n wò lọ́dọọdún láti ìsàlú ọ̀run wọn yóò sì padà sọ́run lọ́hùn-ún. Ìdí nìyí tí wọn ṣe máa ń pe àwọn egúngún yìí ní *'ará ọ̀run kìn-ìn-kin-in'*.

### *4.2 Ètò Ọdún Egúngún Ní Ìlú Olúpọ̀nnà*

Alágbáà ni olórí àwọn egúngún ní ilẹ̀ Yorùbá, bẹ́ẹ̀ ni èyí rí ní ìlú Olúpọ̀nnà náà. Ní ìlú Olúpọ̀nnà, ọ̀tún Ọlọ́jẹ̀ ni igbákejì rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni àwọn ipò mìíràn wà tí ó tẹ̀ lé ọ̀tún Ọlọ́jẹ̀. Àwọn wọ̀nyí ni wọn yóò ṣe ètò ọdún náà tí kò fi ní í sí ìdàrúdàpọ̀ ní ìlú ní àkókò ọdún yìí.

### *4.3 Ìpalẹ̀mọ́ Ọdún*

Ayẹyẹ tí a ń pè ní *'Ọ̀ọ̀lẹ̀ egúngún'* ni ó kọ́kọ́ máa wáyé. Nígbà yìí ni wọn yóò ṣu ọ̀lẹ̀lẹ̀ ọdún bẹ́ẹ̀ ni èyí ni yóò jẹ́ oúnjẹ fún tẹrú tọmọ nínú ìlú láti fi hàn pé ọdún yìí ti bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu.

Kí ó tó di ọjọ́ ọ̀lẹ̀lẹ̀ síṣù yìí ni àwọn olóyè egúngún yóò ti da ọjọ́ mẹ́tàdínlógún tí ọdún náà yóò bẹ̀rẹ̀, tí wọn yóò sì kéde ọjọ́ yìí káàkiri ìlú, bẹ́ẹ̀ ni ọdún yìí máa ń wáyé nínú oṣù keje sí ìbẹ̀rẹ̀ oṣù kẹjọ tí í ṣe àkókò òjò. Èyí ni àkókò tí wọ́n máa ń kórè àgbàdo àti iṣu.

Bí Alágbáà àti àwọn olóyè ẹ̀yìn rẹ̀ bá ti dájọ́ ọdún egúngún ni Alágbáà yóò jó káàkiri ìlú pẹ̀lú àwọn olóyè rẹ̀ lọ́kùnrin àti lóbìnrin. Wọ́n yóò máa kọrin, tí wọn yóò sì máa pèsà egúngún ní mẹ́sàn-án mẹ́wàá. Nípa báyìí ni àwọn ènìyàn yóò mọ̀ pé ọdún egúngún ti fẹ́ẹ̀ bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu. Ní pàtàkì jùlọ, àwọn ọmọ ìlú tí ó wà lóko yóò wálé pẹ̀lú oríṣìíríṣìí ohun jíjẹ bí iṣu, àgbàdo, ewébẹ̀, adìẹ àti àwọn ẹran àbọ́pa tí wọn yóò fi ṣe ọdún. Nígbà tí ọjọ́ ayẹyẹ ọdún bá kú ọjọ́ méjọ, egúngún ọba ni yóò kọ́kọ́ jáde láti fi ara hàn ìlú, tí yóò sì jo ijó bàtá àti àdàpọ̀ ìlù dùndùn, yíká ìlú.

### *4.4 Àkókò Ayẹyẹ Ọdún*

Nígbà tí ayẹyẹ ọdún bá ku ọ̀la, èyí ni ọjọ́ ìkúnlẹ̀, àwọn egúngún bíi egúngún Ọlọ́mọge, egúngún Àyàndáre yóò jáde.

Ní ọjọ́ ayẹyẹ ọdún egúngún yìí, agogo mọ́kànlá àárọ̀ ní àwọn egúngún yóò bẹ̀rẹ̀ sí í jáde. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ èrò ni yóò máa wọ́ tẹ̀lé egúngún kọ̀ọ̀kan lẹ́yìn pẹ̀lú ọrẹ́ àtòrì tí wọn yóò máa fi na ara wọn láti mọ ẹni tí ó bá láyà, tí ó sì kún ojú òṣùnwọn.

Egúngún Alágbáà ni yóò ṣaájú láti jáde, tí àwọn obìnrin ilé yóò sì wọ́ tẹ̀ lé e pẹ̀lú orin ẹ̀sà egúngún. Àwọn ọkùnrin yóò mú ọrẹ́ lọ́wọ́ láti máà jẹ́ kí àwọn èniyàn tẹ aṣọ egúngún mọ́lẹ̀. Pẹ̀lẹ́ pẹ̀lẹ́ ni egúngún yìí yóò máa gbé ẹsẹ̀ pẹ̀lú ijó bàtá títí yóò fi jókòó níbi tí a mọ̀ sí *'Ojúde Àgbà'*, bẹ́ẹ̀ ni Baálẹ̀ àti àwọn Olóyè rẹ̀ yóò jókòó pẹ̀lú rẹ̀.

Lẹ́yìn èyí ni àwọn egúngún mìíràn yóò máa dé, tí wọn yóò sì máa jó dáadáa pẹ̀lú ẹ̀sà egúngún lẹ́nu àwọn èniyàn tí wọ́n tẹ̀lé wọn. Díẹ̀ lára àwọn egúngún tó máa ń jáde ni Egúngún Òjòperè tí iṣe egúngún Baálẹ̀, Egúngún ọlọ́rẹ́, Egúngún Ọlọ́bẹ̀, Egúngún oníbúrẹ́dì, Songíro, Egúngún Ọlọ́sanyìn, Ṣokotí, Adúnkookò, Kòkólowó, Ajóféèbó, Pàjẹ́polóbì, Ṣámọláàáké, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

### *4.5 Ìkáṣẹ̀*

Egúngún tí a mọ̀ sí Pẹlẹbẹ tí í ṣe egúngún ilé Alágbáà ni ó máa ń kaṣè ọdún nílẹ̀ nígbà tí ó bá jó dé gbogbo ìlú, tí ó sì ń wúre fún àwọn èniyàn.

Wọ́n ti sọ àwọn egúngún wọ̀nyí di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ; bẹ́ẹ̀ ni àkàrà, ẹkọ àti epo ni wọ́n fi máa ń bọ wọn. Nígbà yìí ni àwọn obìnrin ìlú, pàápàá àwọn ọmọ oṣú yóò ra oríṣiríṣi aṣọ wá fún egúngún yìí láti tọrọ ohun tí wọ́n bá fẹ́ kí ó ṣe fún wọn, tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn yóò sì máa jẹ́jẹ̀ẹ́ bí ìbéèrè wọ́n bá di mímúṣẹ. Nígbà yìí ni ayẹyẹ ọdún náà yóò wá sí òpin.

### *5.0 Ìsọníṣókí*

Nínú ìpín yìí ni a ti wo ọ̀kan nínú àwọn ìṣẹ̀ṣe ìlú Olúpọ̀nnà, tí ó wà lẹ́bàá ìlú Ìwó. A rí i bí wọ́n ti ń ṣe ọdún egúngún wọn. A bẹ̀rẹ̀ lórí ibi tí ìlú Olúpọ̀nnà wà bẹ́ẹ̀ ni a sọ̀rọ̀' nípa ìgbàgbọ́ wọn nínú àwọn Ìbọ gẹ́gẹ́ bí àṣà àwọn agbègbè yòókú ní ilẹ̀ Yorùbá.

Ìpalẹ̀mọ́ fún ọdún egúngún ni a kọ́kọ́ sọ̀rọ̀ lé lórí àti bí wọ́n ṣe ń ṣe ètò náà tí kì í fi í sí ìdàrúdàpọ̀ àti jàgídíjàgan ní àkókò ayẹyẹ ọdún egúngún náà. A wo àsìkò tí wọ́n máa ń ṣe ọdún yìí bí ó ṣe jẹ́ àkókò ìkórè oko àti àsìkò òjò.

A mọ orúkọ díẹ̀ lára àwọn egúngún tí ó máa ń jáde lọ́dọọdún àti bí ìgbàgbọ́ àwọn ènìyàn náà ṣe rọ̀ mọ́ sísin àwọn Ìbọ, èyí ni àwọn baba àti ìyá wọn tí wọ́n ti papòdà.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Júwe lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́ ibi tí ìlú Olúpọ̀nnà wà ní ilẹ̀ Yorùbá.
2. Báwo ni ọdún egúngún ṣe jẹ mọ́ ẹ̀sìn Yorùbá?
3. Ìpo wo ni ayẹyẹ ọdún egúngún wà ní ìlú rẹ?
4. Dárúkọ àwọn egúngún pàtàkì márùn-ún ní ìlú Olúpọ̀nnà.
5. Dárúkọ àwọn olóyè egúngún mẹ́ta àti ojúṣe wọn ní ìlú rẹ̀.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Ọládìran, A. (1989). 'Ọdún Egúngún Ní Ìlú Olúpọ̀nnà' in *Fèyíkọ́gbọ́n* Vol. 20, Nọ 3, Ìbàdàn, Comedy Publications Company.

Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn, Gavima Press Ltd.

Ọlájubu, O. (1975). *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn, Longman.

Dáramọ́lá, O. & Jẹjẹ, A. (1968). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn, Oníbọn-Ójé Press and Book Industries (Nig.) Ltd.

**MÓDÙ KÌNNÍ**

**ÌPÍN KẸTA:  ỌDÚN ÒKÈBÀDÀN NÍ ÌLÚ ÌBÀDÀN**

***Àkóónú***

1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́: Ọdún Òkèbàdàn Ní Ìlú Ìbàdàn

4.1 Ìṣẹ̀dálẹ̀ Ìlú Ìbàdàn

4.2 Ìdí tí a fi ń ṣe ọdún Òkèbàdàn

4.3 Kín ni Òkèbàdàn fúnra rẹ̀

4.4 Ọdún Òkèbàdàn àti Àwọn Èèwọ̀ to jẹ mọ́ ọn

4.5 Bíbọ Òkèbàdàn

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Ìlú Ìbàdàn jẹ́ ìlú tí ó ólókìkí púpọ̀ ní gbogbo orílẹ̀-èdè Nàìjíríà àti ní àgbáyé lápapọ̀. Ó jẹ́ ìlú tí a tẹ̀dó sáàrín àwọn òkè ńláńlá. Èyí fi ara pẹ́ ìdí tí a ṣe ń ṣe ọdún Òkèbàdàn ní ìlú Ìbàdàn. Ṣùgbọ́n ṣá, kìí ṣe pípọ̀ àwọn òkè yìí ni ó fa ọdún Òkèbàdàn bí kò ṣe àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ kan tí ó mú kí á máa bọ ọ̀kan nínú àwọn òkè yìí, èyí tí ó sì di ìṣẹ̀ṣe wọn títí di oní olónìí. A ó mẹ́nuba bí orírun Ìbàdàn ṣe wáyé àti ìdí tí a fi ń ṣe ìrántí rẹ̀ ní ọdọọdún. Bákan náà ni a ó wo àwọn orin ọdún yìí gẹ́gẹ́ bí ìrántí ohun tí ó ti ṣẹlẹ̀ kọjá, bẹ́ẹ̀ ni a kò gbọdọ̀ gbàgbé láti wo àwọn èèwọ̀ tí ó so mọ́ ọdún náà.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Èròǹgbà Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni láti jẹ́ kí:

- Akẹ́kọ̀ọ́/Òǹkàwé yìí mọ ipò pàtàkì tí Ìlú Ìbàdàn wà láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ àti lóde òní.
- Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mọ̀ nípa bí ọdún Òkèbàdàn ṣe di ọ̀rọ̀ ìṣẹ̀ṣe títí di òní olónìí.
- A le mọ òtítọ́ tí ó rọ̀ mọ́ ìṣẹ̀dálẹ̀ ọdún Òkèbàdàn.
- Àríyànjiyàn tí ó máa ń wáyé nípa ọdún yìí di ohun ìgbàgbé, kí èdè sì yé àwọn aláìmọ̀kan nípa rẹ̀.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Ìpo wo ni Ìlú Ìbàdàn wà nípa ọrọ̀-ajé àti ìgbáyégbádùn orílẹ̀-èdè Nàìjíríà láyé àtijọ́?
2. Òkè mélòó ni ó wà ní Ìlú Ìbàdàn?
3. Kín ni àbùdá tàbí àwọn ohun tí ó mú kí Ìlú Ìbàdàn di gbajúmọ̀ ní orílẹ̀-èdè yìí?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìṣẹ̀dálẹ̀ Ìlú Ìbàdàn

Ìlú Ìbàdàn jẹ́ Ìlú kan tí ó gbajú-gbajà ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà, ó sì jẹ́ Ìlú olókìkí ní Ìwọ̀-Oòrùn Afíríkà àti Ìlú tí ó gbajúmọ̀ ní gbogbo àgbáyé. Ìlú Ìbàdàn yìí ni ìtàn sọ pé ó tóbi jù lọ ní Ìwọ̀-Oòrùn Afíríkà. Yàtọ̀ sí èyí, Ìlú Ìbàdàn wà ní oríta tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn

oníṣòwò ńláńlá sábà máa ń gbáríjọ sí, níbi tí wọn ti máa ń pàdé àwọn oníbàárà wọn láti àwọn ìlú òkè mìíràn.

Ìlú Ìbàdàn yìí jẹ́, ìlú tí àwọn akọni máa ń sá lọ pàápàá ní àkókò ogun abẹ́lé àti ogun ẹlẹ́yàmẹ̀yà ìgbàanì. Ìbàdàn ni àkójọpọ̀ àwọn jagunjagun tẹ̀dó sí, bẹ́ẹ̀ ni àwọn jagunjagun wọ̀nyí ni wọ́n gba Yorùbá sílẹ̀ lọ́wọ́ ogún àwọn Fúlàní tí ó fẹ́ kó Yorùbá lẹ́rú nígbà náà. Ìtàn sọ fún wa pé Lágelú tí í ṣe akọni láti Ilé-Ifẹ̀ ni ó tẹ Ìlú Ìbàdàn dó ni ìgbà ìwáṣẹ̀.

## 4.2 Ìdí tí wọ́n fi ń ṣe Ọdún Òkèbàdàn

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, bí kò bá nídìí, obìnrin kì í jẹ́ kúmólú. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ lókè yìí pé jagunjagun, Lágelú, láti Ilé-Ifẹ̀ ni ó wá sí Ẹ̀bá-Ọ̀dàn tí a mọ̀ sí Ìbàdàn lónìí, tí ó sì tẹ̀dó síbẹ̀ pẹ̀lú àwọn ọmọlẹ́yìn rẹ̀ kan nígbà náà, ṣùgbọ́n nígbà tí àwọn ènìyàn rẹ̀ kan dorí àṣà kodò nípa bíbọ́ aṣọ lójú egúngún, èyí tí ó jẹ́ èèwọ̀ láàrín àwọn Yorùbá, ni àgbáríjọpọ̀ ìran Yorùbá yòókù gbógun tì wọ́n, tí wọ́n sì sá gun Òkè kan lọ ní agbègbè Àwọ́tán láti fi ara pamọ́ lórí òkè náà fún ìgbà díẹ̀.

Ó ṣeni láàánú pé àwọn ọ̀tá yípo Òkè náà fún àkókò pípẹ́ nítorí pé wọ́n lérò pé àwọn ogun Ìbàdàn tí wọ́n sá gún orí òkè yìí yóò tètè sọ̀ kalẹ̀ nígbà tí ọwọ́ ebi bá tẹ̀ wọ́n. Ṣùgbọ́n sá, Ọlọ́run kẹ́ àwọn ọmọ-ogun Ìbàdàn nígbà tí wọ́n ń rí òro jẹ, tí wọ́n sì ń rí ìgbín fi ṣe ọbẹ̀ jẹ fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún. Bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ń gbin àgbàdo tí wọn fi ń mu ẹ̀kọ́.

Nígbà tí àwọn ọmọ ogun Yorùbá rí í pé àwọn ọmọ-ogun Ìbàdàn kò sọ̀kalẹ̀ mọ́, wọ́n bá ọ̀nà wọn lọ. Ṣùgbọ́n sá o, obìnrin iwin kan tí ó tẹ̀dó sínú àpáta ńlá kan lorí òkè yìí yọ́nú sí wọn. Ó ń kẹ́ wọn, ó sì ń gẹ̀ wọn, bẹ́ẹ̀ ni kò pa wọ́n lára rárá. Ìdí nìyí tí Abọ̀kè ṣe máa ń dirun rẹ̀, tí àwọn obìnrin yóò sì wé gèlè fún un ní àsìkò ọdún Òkèbàdàn.

## 4.3 Kín ni Òkèbàdàn Fúnrarẹ̀?

Òkèbàdàn ni ó máa ń tọka sí obìnrin iwin tí ó ń gbé inú Àpáta ní orí òkè Àwọ́tán tí a ti mẹ́nubà lókè yìí. Òun ni ó máa ń sọ àsọtẹ́lẹ̀ fún Lágelú tí íṣe baba ogun Ìbàdàn nígbà náà.

Nígbà tí àwọn ogun Yorùbá tí ń lépa ogun Ìbàdàn tí lọ tán, Lágelú pinnu láti fi òkè Àwọ̀tán sílẹ̀ láti lọ tẹ̀dó sí iwájú, bẹ́ẹ̀ ni Ifá gbà wọ́n ní ìmọ̀ràn ibi tí wọn yóò tẹ̀dó sí.

A kò ní í sàìrántí pé lẹ́yìn ìgbà tí Lágelú àti àwọn ọmọ-ogun rẹ̀ fi orí òkè yìí sílẹ̀ tán ni ara àwọn ọkùnrin wọn kò gbé pépé mọ́, bẹ́ẹ̀ ni ara àwọn obìnrin wọn náà kò gbéra. Èyí ni ó jẹ mọ́ ẹsẹ̀ Ifá kan tí ó sọ pé:

Aboyún kò bí mọ́
Àgàn kò tọwọ́ àlà bosùn
Ọ̀kùnrùn kò dìde
Àtọ̀ gbẹ mọ ọkùnrin nídìí
Obìnrin kò rí àṣẹ rẹ̀ mọ́
Ọmọge gúnmú, ọmú gbẹ….

Èyí ni ó fà á tí Lágelú fi lọ bèèrè lọ́wọ́ Ifá pé kín ni àwọn yóò ṣe láti bọ sípò, bẹ́ẹ̀ ni Barapetu ní kí wọ́n ó ṣe ìrúbọ ní; wọ́n sì ṣe èyí. Láti ìgbà náà ni wọn kò ti lè gbàgbé ìrírí wọn lórí Òkè Àwọ̀tán, èyí tí wọ́n ń ṣe ìrántí rẹ̀ lọ́dọọdún.

## 4.4 Ọdún Òkèbàdàn àti Àwọn Èèwọ̀ Tó jẹ mọ́ ọn

A ti mọ ohun tí ọdún Òkèbàdàn dá lé lórí ṣùgbọ́n ó yẹ kí a mọ àsìkò tí wọ́n máa ń ṣe é àti àwọn èèwọ̀ tí ó jẹ mọ́ ọdún náà.

Ní ìdajì oṣù kẹta ọdún ni wọ́n sábà máa ń ṣe Ọdún Òkèbàdàn ní Ìlú Ìbàdàn. Tilé toko ni wọ́n máà ń pé sibẹ̀ ní ọdọọdún láti ṣe ìrántí ìṣẹ̀lẹ̀ mánigbàgbé tí ó ṣẹlẹ̀ sí wọn lórí òkè Àwọ̀tán, ìrírí àti ìyá tí ó jẹ wọn, tí ó sì di ayọ̀ fún wọn nígbẹ̀yìn.

Àwọn èèwọ̀ kan wà tí ó jẹ mọ bíbọ àti ṣíṣe ọdún Òkèbàdàn yìí. Ọ̀kan lára rẹ̀ ni pé ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ dána tàbí rú èèfín lọ́jọ́ náà. Ilékílé tí wọ́n bá ti dá iná lọ́jọ́ náà, ìgbóná yóò jà nínú irú ilé bẹ́ẹ̀. Òmíràn ni pé ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ bínú tàbí jà nítorí orin Òkèbàdàn, bẹ́ẹ̀ ni ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe àìgbọràn sí èyí yóò jìyà, yóò sì jẹ ewé iyá.

Ọjọ́ kan ṣoṣo ni wọ́n máa ń lò láti ṣe ọdún Òkèbàdàn bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Abọ̀kè àti àwọn ọmọlẹ́yìn rẹ̀ máa ń ṣe àìsùn nígbà tí ọjọ́ ọdún bá ku ọ̀la. Ọdún Òkèbàdàn kò jẹ mọ́ ẹ̀sìn bí kò ṣe ọdún ìṣẹ̀ṣe tí wọ́n ń rántí ohun ìṣẹ̀lẹ̀ ìyanu tí ó ti kọjá lọ.

### 4.5 Bíbọ Òkèbàdàn

Ọba Ìlú ni ó sábà máa ń pèsè àwọn ohun ìrúbọ fún ọdún Òkèbàdàn. Lára àwọn ohun ẹbọ náà ni:

1. Màálúù kan
2. Ewúrẹ́ kan
3. Àgùtàn kan
4. Ajá kan
5. Igba Ìgbín
6. Igba Ẹyẹlé
7. Igba Obì àbàtà
8. Igba Orógbó

Abọ̀kè àti àwọn àwòrò rẹ̀ ni yóò lọ sí òkè Àwọ̀tán tí wọn yóò sì lọ ṣe àwọn ètùtù yìí, bẹ́ẹ̀ ni bí wọ́n bá ti ṣe èyí tán, tí wọ́n sì lọ sí Ilé Ọ̀sẹ́ méjì ni Ọjà-Iba, ó parí nìyẹn. Òjò sábà máa ń rọ̀ lẹ́yìn ètùtù yìí ní ọdọọdún láti fi hàn pé ẹbọ fín, ẹbọ dà.

### 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín yìí ni a ti wo Ọdún Òkèbàdàn gẹ́gẹ́ bí ọdún ìṣẹ̀ṣe tí kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn ní Ìlú Ìbàdàn. Ní ìbẹ̀rẹ̀, a wo àwọn ipò tí Ìbàdàn wa ní àwùjọ orílẹ̀-èdè àti ní gbogbo àgbáyé bẹ́ẹ̀ ni a rí i dájú pé kò sí irú kán-ún láwùjọ òkúta, bẹ́ẹ̀ ni kò sí irú iyọ̀ láwùjọ yẹ̀rẹ̀pẹ̀. Eegun bí eyín sọ̀wọ́n ni ọ̀rọ̀ Ìbàdàn jẹ́ lágbàáyé nínú àṣà, ẹ̀sin, ọrọ̀-ajé, ìṣèlú àti amúlùúdùn.

A sọ̀rọ̀ ohun tí ó fà á tí ọdún Òkèbàdàn fi di ọdún ìṣẹ̀ṣe tí tẹ́rutọmọ ń káràmáásìkí rẹ̀. A sọ̀rọ̀ nípa àwọn èèwọ̀ tí ó jẹ mọ́ ọn láyé àtijọ́ bẹ́ẹ̀ ni a jẹ́ kí á mọ̀ pé ṣíṣe ọdún Òkèbàdàn kò papọ̀ mọ́ ẹ̀sìn rárá.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Òkè wo ni a máa ń tọ́kasí gẹ́gẹ́ bí Òkèbàdàn àti pé kín ni ó fà á ti wọ́n fi ń bọ ọ́?

2. Kín ni ìyàtọ̀ àti ìjọra tí ó wà ní bíbọ Òkèbàdàn àti Ẹ̀sìn?

3. Ṣàlàyé kíkún lórí àwọn èèwọ̀ tó jẹ mọ́ ọdún Òkèbàdàn.

4. Ṣàlàyé ọdún ìṣẹ̀ṣe mìíràn, bóyá ní Ìlú rẹ tàbí níbòmíràn.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Fálọlá, Tóyìn (2012). *Ìbàdàn: Foundation, Growth and Change 1830-1960*. Ìbàdàn: Book Craft.

Llyod, P.C. *et al* (1967). *The City of Ìbàdàn.* New York: Cambridge University Press.

Awẹ́, B. (1969). "The Rise of Ìbàdàn as a Yorùbá Power in the 19th Century". Ph.D Thesis, Oxford University.

Adékọ́lá, O.O. & Àlàmú, O. (1991). *Òkèbàdàn: Discussions on the Significance of Òkèbàdàn Festival in Contemporary Period.* Ìbàdàn, Kọ́lápọ̀ Press.

Ọyádèjì, B. (1990). *Ọdún Òkè-èbàdàn Ní Ìlú Ìbàdàn*. Ìbàdàn Comedy Publications Company.

Morgan, Kẹmi nd. *Outline History of Ìbàdàn.* Ìbàdàn, Caxton Press.

**MÓDÙ KÌNNÍ**

**ÌPÍN KẸRIN: *ỌDÚN BẸẸRẸ NÍ ÌLÚ Ọ̀YỌ́***

***Àkóónú***

1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ìtumọ̀ Bẹẹrẹ

4.2 Ipò Aláàfin àti Àṣẹ Pípa Bẹẹrẹ

4.3 Ayẹyẹ Ọdún Bẹẹrẹ

4.4 Àwọn ìlú Àmọ́nà

4.5 Ìparí Ọdún Bẹẹrẹ

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Lára ìṣẹ̀ṣe Yorùbá ní ọdún Bẹẹrẹ wà ní Ìlú Ọ̀yó. Èyí jẹ́ ọdún pàtàkì kan tí Aláàfin àti àwọn Ọ̀yọ́mèsì máa ń kópa nínú rẹ̀ lọ́dọọdún.

Ọdún Bẹẹrẹ dá lórí gígé koríko kan tí wọ́n máa ń lò láti fi bo ààfin ọba ìlú Ọ̀yọ́ lórí gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀ pé ewé tàbí koríko ni àwọn Yorùbá máa ń lò láti má jẹ́ kí òjò omi wọ inú ilé nígbà náà.

Ayẹyẹ ọdún Bẹẹrẹ yìí máa ń lárinrin nítorí pé gbogbo ìlú àmọ́nà tí Aláàfin tó wà lábẹ́ àkóso káàkiri  agbègbè rẹ̀ ni ó gbọdọ̀ lọ́wọ́ sí ọdún yìí nípa pípa òbítíbítí ẹrù koríko bẹẹrẹ lọ fún Aláàfin láti fi tún ààfin rẹ̀ kọ́. Ọjọ́ márùn-ún ni wọ́n máa ń fi ṣe ọdún yìí, bẹ́ẹ̀ ni ayẹyẹ yìí máa ń lárinrin. Wàyí o, ọdún Bẹẹrẹ kò lárinrin mọ bíi ti àtijọ nítorí pé a kò lo koríko tàbí ewé mọ́ láti bo ilé lóde òní àti pẹ̀lú pé gbogbo àwọn ìlú àmọ́nà tí wọ́n wà lábẹ́ Aláàfin Ọ̀yọ́ ni wọ́n ti di Olómìnira. Ṣùgbọ́n ṣá o, ìṣẹ̀ṣe yìí kò parẹ́ nítorí pé wọ́n sì ń ṣe é gẹ́gẹ́ bí orò ilé àti pé wọ́n kàn ń pa koríko yìí ní ìwọ̀nba láti fi ṣe àṣẹ àti ìrántí ní.

## 2.0 Èròǹgbà Àti Àfojúsùn

Èròǹgbà ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni;

- Láti jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ mọ ipò Aláàfin ní Ilẹ̀ Yorùbá láyé àtijọ́.
- Láti jẹ́ kí a mọ bí a ṣe ń kọ́ ilé àti àwọn ohun èlò tí a fi máa ń bò ó ní ayé ìgbàanì.
- Kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè mọ̀ pàtàkì ọdún Bẹẹrẹ ní àkókò tí a ń wí yìí.
- Láti jẹ́ kí òǹkàwé àti akẹ́kọ̀ọ́ rí ìyípadà tí ọ̀làjú ti mú bá bí a ṣe ń kọ́lé lóde òní.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájum:

1. Sọ ohun tí o mọ̀ nípa Aláàfin àti àwọn ìjòyè rẹ̀ .
2. Dárúkọ àwọn Ìlú Àmọ́nà márùn-ún tí ó wà lábẹ́ Aláàfin láyé àtijọ́.
3. Ìyípadà wo ni ọ̀làjú ti mú bá ètò ilé kíkọ́ lóde òní?
4. Kín ni èrò tìrẹ lórí àsìngbà tí àwọn ìlú kéréje kéréje máa ń sìn lábẹ́ Aláàfin láyé àtijọ́?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ohun tí Ọdún Bẹẹrẹ dá lé lórí

Ọdún Bẹẹrẹ jẹ́ ara ọdún ìṣẹ̀ṣe tí a mọ̀ mọ Aláàfin àti àwọn Ọ̀yọ́mèsì, èyí tí ó gbajú-gbajà káàkiri Ìlú Ọ̀yọ́ àti agbègbè rẹ̀.

Ọdún Bẹẹrẹ dá lé àwọn nǹkan tí àwọn ìlú kéréje kéréje má ń mú lọ fún Aláàfin láti fi ìmọrírí wọn hàn sí ọba náà. Yàtọ̀ sí àwọn ẹ̀bùn mìíràn, koríko Bẹẹrẹ jẹ́ dandan fún àwọn Baálẹ̀ ìlú agbègbè Ọ̀yọ̀ láti pa ránṣẹ́ sí Ọ̀yọ́ fún àtúnkọ́ ààfin. A kò ní í sàì rántí pé àwọn ìlú agbègbè Ọ̀yọ́ mìíràn wà lára àwọn tí ó máa ń pa bẹẹrẹ fún Aláàfin. Ó ṣe pàtàkì láti fi yé wa pé oríta ibi tí àwọn Ìbàdàn máa ń kó koríko Bẹẹrẹ yìí jọ sí kí wọ́n tó kó o lọ sí Ọyọ́ ni a mọ̀ sí adúgbò Bẹẹrẹ ní Ìbàdàn títí di òní olónìí.

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ síwájú, ọdún Bẹẹrẹ kò fi bẹ́ẹ̀ rajaja mọ́ lóde òní bí kò ṣe pé wọ́n ń ṣe ìrántí ìṣẹ̀ṣe yìí nípa bíbọ orò ilé ní Ọ̀yọ́ Aláàfin.

Bẹẹrẹ ní Ìlú Ọ̀yọ́ láyé àtijọ́. Kí ayẹyẹ ọdún tó bẹ̀rẹ̀, àwọn babaláwo máa ń dá Ifá láti mọ àkókò àti ìgbà tí ó tùbà tùṣẹ láti bẹ̀rẹ̀ ọdún náà. A sọ fún wa pé ọdún yìí sábà máa ń wáyé nínú Oṣù Èrèlé (February) èyí tí í ṣe oṣù kejì ọdún Òyìnbó; ṣùgbọ́n Ifá ni yóò sọ àkókò àti ọjọ́ gan-an tí ọdún máa bẹ̀rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí Akíntáyọ̀ ṣe sọ, “kò sí kókó ọjọ́ kan nínú oṣù yìí fún ìbẹ̀rẹ̀ ọdún náà” (Akíntáyọ̀, 1991:8).

Bí Ifá bá sọ pé kí wọ́n ní ọjọ́ mẹ́sàn-án tàbí ọjọ́ mẹ́tàdínlógún lẹ́yìn tí Barapetu bá ti fọhùn tán. Lẹ́yìn èyí, ohun tí ó kàn ni láti fi tó Aláàfin létí ohun tí Ifá sọ, bẹ́ẹ̀ ni akéde Ọba yóò lu agogo káàkiri Ìlú, tí ìmúrasílẹ̀ yóò sì bẹ̀rẹ̀ ni pẹrẹu.

### 4.3 Ìbẹ̀rẹ̀ Ọdún Bẹẹrẹ Gan-an

Lẹ́yìn tí wọ́n bá ti kéde, tí ọjọ́ sì ku ọ̀la ni àìsùn ọdún yóò wáyé, bẹ́ẹ̀ ni gbogbo àwọn olóyè àti àwọn Baálẹ̀ Ìlú agbègbè yóò wá sí Ààfin pẹ̀lú ẹ̀bùn tí ó jọjú fún Ọba, pẹ̀lú ìtì koríko bẹẹrẹ fún àtunkọ Ààfin. Pẹ̀lú ìlù, orin àti ijó ni wọ́n fi máa ń ṣe ayẹyẹ ọdún yìí nínú ààfin, bẹ́ẹ̀ ni ọjọ́ márààrún ni wọn yóò fi ṣe àìsùn.

A sọ fún wa pé àwọn egúngún yóò máa jó wá sínú ààfin pàápàá jùlọ egúngún Aṣẹ́yìn Tí wọ́n ń pè ní Alátẹ-ọ̀run, tí o máa ń tẹ̀lé Asẹ́yìn lọ sí ibi ayẹyẹ náà yóò máa dá àwọn ènìyàn lára ya, pàápàá nínú àìsùn òru náà.

## 4.4 Ìparí Ọdún Bẹẹrẹ

Àìsùn ọjọ́ karùn-ún mọ́jú ni yóò fi ìparí ayẹyẹ ọdún náà múlẹ̀. Nígbà yìí ni àwọn ẹrú (ìlàrí) Ọba yóò gbé ẹbọ ọdún ní ìhòòhò ọmọlúàbí yíká gbogbo ibodè tí ó wọ ìlú Ọ̀yọ́, bẹ́ẹ̀ ni wọn kò gbọdọ̀ pàdé ènìyàn lọ́nà títí wọn yóò fi padà wọnú ààfin. Ní kété tí àwọn tí ó gbé ẹbọ yìí bá ti padà wọnú ààfin ni Aláàfin, Ọ̀yọ́mèsì àti gbogbo ènìyàn yóò jo lọ sí ilé Mọlẹ̀ àti Ilé Ọ̀sanyìn nínú ààfin.

Nígbà tí ilẹ̀ ọjọ́ karùn-ún bá mọ́ wàyí o, wọn yóò ṣe àsè ńlá tí wọ́n ń pè ní Ọ̀sínmíní fún àwọn olùkópa àti àlejò Aláàfin bẹ́ẹ̀ ni bí wọ́n bá ti parí wẹ̀jẹ-wẹ̀mu yìí, àwọn àlejò Aláàfin yóò padà máa lọ sí ibùgbé wọn.

## 5.0 Ìsọníṣókí

A ti wo ọdún Bẹẹrẹ ní Ìlú Ọ̀yọ́ gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan nínú ọdún ìṣẹ̀ṣe tó lààmìlaaka ní Ìlú Ọ̀yọ́ àti agbègbè rẹ̀ ní ayé àtijọ́. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọdún yìí kò gbajúgbajà mọ́ lóde òní, a rí i pé ọdún ìṣẹ̀ṣe náà kò parun, nítorí pé wọ́n ti sọ ọ di orò ilé.

A ṣe àyẹ̀wò ohun tí ó máa ń ṣẹlẹ̀ ní àkókò ọdún ìṣẹ̀ṣe yìí, a sì rí bí ọ̀làjú ṣe mú àyípadà ńlá bá a. A ṣe àlàyé bí a ṣe ń ṣètò ọdún náà tí ó fi máa ń lárinrin tí inú ọ̀pọ̀lọpọ̀ olùkópa yóò sì dùn padà sí ilé wọn. A gbọ́ pé ọjọ́ márùn-ún ni wọ́n fi máa ń ṣe ọdún yìí pẹ̀lú ní tìlù tìfọn, tí wẹ̀jẹ-wẹ̀mu yóò sì kásẹ̀ rẹ̀ nílẹ̀.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ipò wo ni Ìlú Ọ̀yọ́ wà ní Ilẹ̀ Yorùbá láyé àtijọ́ àti lóde òní?
2. Àwọn wo ni a ń pè ní *'Ọ̀yọ́mèsì'* nínú ètò ìṣèlú Aláàfin láyé àtijọ́?
3. Sọ lẹ́kùn-ún-rẹ́rẹ́ ohun tí ọdún Bẹẹrẹ dá lé lórí.
4. Dárúkọ àwọn egúngún pàtàkì ní ìlú rẹ.
5. Kín ni ìdí pàtàkì tí a fi ń pe agbègbè kan ní Bẹẹrẹ ní Ìlú Ìbàdàn?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Johnson, S. (1921). *History of the Yorùbás.* From the Earliest Tunes to the Begnning of the Protectorate, Lagos, C.M.S.

Akíntáyọ̀, J.O. (1991). "Ọdún Bẹẹrẹ Ní Ìlú Ọ̀yọ́" in *Fèyíkọ́gbọ́n.* Ìbàdàn, Comedy Publications Company.

Bíòbákú, S.O. (1973). *Sources of Yorùbá History.* Oxford, Oxford University Press.

## MÓDÙ KÌNNÍ

## ÌPÍN KARÙN-ÚN: ORÒ ÌKẸ̀GBẸ́ NÍ ÌLÚ ÌLÁ-Ọ̀RÀNGÚN

***Àkóónú***

1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Kín ni Ìkẹ̀gbẹ́ gẹ́gẹ́ bí Ìṣẹ̀ṣe?

4.2 Ìdí tí a fi ń ṣe ọdún Ìkẹ̀gbẹ́ àti bí a ti ń ṣ é.

4.3 Ìbẹ̀rẹ̀ Ọdún Ìkẹ̀gbẹ́

4.4 Ìpalẹ̀mọ́ fún Ọdún Ìkẹ̀gbẹ́

4.5 Èèwọ̀ tó Rọ̀ mọ́ Ọdún Ìkẹ̀gbẹ́

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Ọdún Ìkẹ̀gbẹ́ jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú ọdún ìṣẹ̀ṣe ní Ìlú Ìlá-Ọ̀ràngún. Ìlú yìí wà ní ibi tí a mọ̀ sí Ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun ní Òde-òní, bẹ́ẹ̀ ni kò jìnnà sí ìlú Òṣogbo tí í ṣe olú-ìlú Ìjọba Ìpínlẹ̀ náà.

Ọdún Ìkẹ̀gbẹ́ yìí ni a lè tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ọdún orò kan tí àwọn ìjòyè ọba ìlú Ìlá-Ọ̀ràngún máa ń ṣe fún ìrántí ìpapòdà ọ̀kan nínú àwọn olóyè yìí. Nípa báyìí, ọdún yìí kì í ṣe ohun tí wọ́n máa ń ṣe ní ọdọọdún bí kò ṣe pé nígbà tí ọmọ ẹgbẹ́ kan bá sílẹ̀ bora. Èyí sì ni ètùtù orò ìṣẹ̀ṣe tí wọ́n máa ń ṣe fún ìrántí àwọn ọmọ ẹgbẹ́ náà tó ti ta téru nípàá.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Èròǹgbà ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni láti:

- Jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ lóye nípa ọdún ìṣẹ̀ṣe Ìkẹ̀gbẹ́ yìí.
- Mú kí wọ́n mọ̀ pé ìṣẹ̀ṣe yìí fi ara pẹ́ orò ìṣípà ọdẹ tí àwọn ọdẹ Yorùbá máa ń ṣe lẹ́yìn akọni ọdẹ.
- Ṣàlàyé ohun tí orò Ìkẹ̀gbẹ́ yìí dá lé lórí.
- Mú kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mọ̀ pé kì í ṣe orò tí a ń ṣe lọ́dọọdún.
- Lè fihàn akẹ́kọ̀ọ́ pé orò ìṣẹ̀ṣe yìí náà máa ń wáyé ní Ìlú Òkè Ìlá tí í ṣe ìbátan kan náà pẹ̀lú àwọn ènìyàn Ìlú Ìlá-Ọ̀ràngún.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Níbo ni Ìlú Ìlá-Ọ̀ràngún wà ní Ilẹ̀ Yorùbá?
2. Ṣe àfiwé ọdún Ìkẹ̀gbẹ́ àti orò Ìsípà ọdẹ láàrín àwọn Yorùbá.

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ohun tí Ọdún Ìkẹ̀gbẹ́ Dá lé lórí

Ọdún Ìkẹ̀gbẹ́ jẹ́ ọdún orò kan tí wọ́n máa ń ṣe ní Ìlú Ìlá-Ọ̀ràngún, èyí tí ó máa ń mú kí wọ́n máa ṣe ìrántí àwọn olóyè ìlú tí ó bá ti fi ilẹ̀ bora bí aṣọ.

Ọdún yìí máa ń fi ara jọ ìpà ọdẹ sísí nígbà tí àwọn Yorùbá bá ń ṣe orò fún àwọn akọni ọdẹ tó bá pa ipò dà. Ṣùgbọ́n ọdún ìkẹ̀gbẹ́ yìí tún yàtọ̀ fún ìpà ọdẹ sísí bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kì í ṣe ọdọọdún ni ó máa ń wáyé bí kò ṣe àsìkò tí ìjòyè kan bá papòdà. A kò lè sọ pàtó ohun tí ọ̀rọ̀ yìí (Ìkẹ̀gbẹ́) jẹ́ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó ti di ọ̀rọ̀ àtijọ́ gẹ́gẹ́ bí *'ìpà'* tí àwọn ọdẹ máa ń ṣe.

### 4.2 Ìdí tí a fi ń ṣe ọdún Ìkẹ̀gbẹ́

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, bí kò bá nídìí, obìnrin kìí jẹ́ kúmólú, èyí ni pé ó nídìí tí wọ́n fi ń ṣe orò Ìkẹ̀gbẹ́ ní Ìlú Ìlá-Ọ̀ràngún. Ìdí kan pàtàkì tí wọ́n fi ń ṣe ọdún Ìkẹ̀gbẹ́ yìí ni láti ṣe ètùtù lẹ́yìn ikú ọ̀kan nínú àwọn olóyè ìlú, kí ẹ̀yìn òkú bẹ́ẹ̀ lè dára, kí ìlú sì wà ní ìrọwọ́rọsẹ̀. Èyí tún jẹ́ ìjọra pàtàkì tí ó wà láàrin ìsípà ọdẹ àti ọdún Ìkẹ̀gbẹ́.

### 4.3 Ìpalẹ̀mọ́ fún Ọdún

Ìtàn fi yé wa pé wọ́n dá orò Ìkẹ̀gbẹ́ yìí sílẹ̀ ní àsìkò Ọwáràngún tí ó jẹ sìkejì ní Ìlú Ìlá-Ọ̀ràngún, ẹni tí orúkọ oyè rẹ̀ ń jẹ́ Ọ̀ràngún Àmọ̀tagèsì bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ṣe orò yìí fún Ọba Àmọ̀ta lẹ́yìn tí ó ti wàjà. Láti ìgbà yìí ni ọdún orò Ìkẹ̀gbẹ́ yìí sì ti di igi àlọ́yè títí di àkókò yìí.

Nígbà tí ọjọ́ orò yìí bá ti sún mọ́lé ni Ọ̀ràngún yóò ti ṣe ìkéde fún ará ìlú láti gbọ́ pé ọdún náà yóò wáyé. Ìkéde yìí ṣe pàtàkì láti jẹ́ kí oníkálukú ènìyàn ìlú gbé inú ilé wọn ní ọjọ́ orò yìí, àti pé ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ jáde síta ní ọjọ́ náà títí ètò ọdún náà yóò fi parí. Kódà, láyé òde-òní, àwọn ilé-ìwé gbogbo ní ìlú ni alágogo ọba yóò dé láti kìlọ̀ fún wọn láti so ewé agbéjẹ́ẹ́ mọ́wọ́, kí wọ́n bọ̀wọ̀ fún ọdún ìṣẹ̀ṣe yìí. Ṣùgbọ́n ṣá, agogo mẹ́rin-àbọ̀ ìrọ̀lẹ́ ni ìséde náà yóò parí.

## 4.4 Ìbẹ̀rẹ̀ Ọdún Orò Ìkẹ̀gbẹ́

Ní ọjọ́ orò yìí gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ síwájú, ṣíṣe orò yìí máa ń gba ọjọ́ kan bẹ́ẹ̀ ni ètò orò ṣíṣe máa ń pín sí abala méjì. Èyí ni pé bí ó bá jẹ́ pé àgbà oyè ni ó bá kú, àwọn ọmọ ẹgbẹ́ yóò ṣe orò náà kíámọ́sá ni, ṣùgbọ́n bí ó bá jẹ́ pé ọmọdé ẹgbẹ́ ni, wọ́n níláti so ayẹyẹ orò ẹni bẹ́ẹ̀ rọ̀ di ìgbà tí àgbà ẹgbẹ́ kan bá pa ipò dà ni, tí wọn yóò sì ṣe orò náà papọ̀. Èyí tún yàtọ̀ sí ohun tí o máa ń ṣẹlẹ̀ ní àsìkò orò ìpà fún akọni ọdẹ.

Ní agogo mẹ́wàá òwúrọ̀ ni ètò orò yìí máa ń bẹ̀rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni yóò parí ní agogo mẹ́rin ìrọ̀lẹ́. Nígbà tí àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Ìkẹ̀gbẹ́ bá jáde, gbogbo àwọn ènìyàn ìlú yóò ti sá wọnú ìyẹ̀wù lọ nítorí pé àwọn ènìyàn ìlú kò gbọdọ̀ mọ̀ wọ́n.

Nínú ilé ẹni tí ó kú ni wọn yóò ti pèsè ohun tí wọn yóò lò fún orò ẹni tí ó ti di olóògbé yìí. Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ kọ̀ọ̀kan níláti mú àdá àṣẹ wọn lọ́wọ́ (Àdá Àmọ̀ta) nítorí Ọba Ọ̀ràngún tí ó ń jẹ́ Àmọ̀ta ni ó dá ọdún orò yìí sílẹ̀. Ọjà-Ọba ni àwọn ọmọ ẹgbẹ́ yìí yóò fi orí le nígbà tí wọ́n bá ti kúrò ní ilé, wọn yóò dúró nídìí igi Ìkẹ̀gbẹ́ tó wà láàrín ọjà. Lẹ́yìn èyí ni olórí àwọn ọmọdé ẹgbẹ́ pẹ̀lú àwọn ọmọ ẹgbẹ́ díẹ̀ yóò lọ di ẹrù Ìpà òkú ẹni náà ṣùgbọ́n wọn kì í gbé ẹni Ìpà yìí lọ sínú igbó gẹ́gẹ́ bíi àwọn akọni ọdẹ ṣe máa ń ṣe. Dípò èyí, wọn yóò gbé ẹrù Ìpà náà sí ojú oórì òkú náà, tí wọn yóò sì padà sí àárìn ọjà. Lẹ́yìn èyí, àwọn ọmọ ẹgbẹ́ yìí yóò fi àdá Àmọ̀ta wọn lalẹ̀ ní ojú ọ̀nà ní ìgbà mẹ́ta nígbà tí wọ́n bá ń lọ sí ilé ẹni tí wọ́n ń ṣe orò yìí fún. Wọn yóò pòòyì ilé ẹni náà láti àárìn ọjà fún ìgbà mẹ́ta bí ó bá jẹ́ ọmọdé ni ẹni náà, ṣùgbọ́n bí ó bá jẹ́ àgbàlagbà ni, ìgbà méje ni wọn yóò ṣe ìpòòyì yìí, tí wọn yóò sì fi àdá Àmọ̀ta lalẹ̀ ní ìgbà méje.

Ayẹyẹ yìí kò sàì wáyé pẹ̀lú ìwẹ̀jẹ̀wẹ̀mu, bẹ́ẹ̀ ni onírúurú oúnjẹ bí iyán, ẹ̀kọ, àkàrà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni wọn yóò máa jẹ kí wọ́n tó mu ẹmu lé e. Lẹ́yìn èyí ni Ọlọ́wọ-ọfẹ tì í ṣe olórí ẹgbẹ́ yóò ṣàájú ìwúre fún gbogbo ènìyàn Ìlú Ìlá-Ọ̀ràngún àti àwọn akọni ìlú náà tí wọ́n ti papòdà. Lẹ́yìn ìwúre yìí ni wọn yóò ṣe ètùtù kí Ìlú lè tùbà tùṣẹ fún tẹrú tọmọ. Lẹ́yìn tí wọ́n bá ti parí ètùtù, tí wọ́n sì ti wúre tán, àwọn ọmọ ẹgbẹ́ yóò padà sí àárin ọjà, bẹ́ẹ̀ni níbí sì ni oníkálukú yóò ti padà sí ilé rẹ̀.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ti ṣàlàyé ohun tí orò Ìkẹ̀gbẹ́ dá lé lórí èyí tí ó jẹ mọ orò ìsìnkú àwọn ọmọ ẹgbẹ́ tí ó ti pa ipò dà.

A ménuba àwọn ìjọra àti ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin ọdún orò yìí àti orò ìṣípà àwọn akọni ọdẹ, a sì jẹ́ kí á mọ̀ pé wọn kàn jọra ni, wọn kì í ṣe nǹkan kan náà. A sọ ìdí tí wọ́n fi ń ṣe orò yìí àti àwọn ètò tí wọn máa ń gbà ṣe é pẹ̀lú àkókò ṣíṣe orò náà.

Ní ìparí, a wo ayẹyẹ àti ètò orò náà bí wọ́n ṣe ń ṣe é títí di àsìkò yìí. Ní pàtó, a wo ọdún orò yìí gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan nínú ìṣẹ̀ṣe Yorùbá tí kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Sọ ohun tí o mọ̀ nípa ọdún tàbí orò ìṣẹ̀ṣe kan ní Ìlú rẹ.
2. Sọ ìjọra àti ìyàtọ̀ tí ó wà láàrín orò Ìkẹ̀gbẹ́ ní Ìlú Ìlá-Ọ̀ràngún àti orò Ìṣípà ọdẹ láàrin àwọn Yorùbá.
3. Ṣe àlàyé nípa ohun tí o mọ̀ nípa orò Ìkẹ̀gbẹ́ ní Ìlú Ìlá-Ọ̀ràngún àti ìdí tí wọ́n fi máa ń ṣe orò yìí.
4. Kín ni ìdí tí wọn kò fi gbọdọ̀ rí àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Ìkẹ̀gbẹ́ lójúkorojú ní ọjọ́ ayẹyẹ orò ẹgbẹ́ náà.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá. Ìbàdàn: Gavima Press Ltd.

Sàlámì, A. (2008). *Yorùbá Theology and Tradition.* Lagos: NIDD Publishing Company Limited.

Ayálàágbé, B. (1981). "Orò Ìkẹ̀gbẹ́ Ní Ìlú Ìlá-Ọ̀ràngún" in *Yorùbá Gbòde* (August 1981). Ìbàdàn: Macmillian Nigeria Publishers Limited.

Sheba, L. (2011). "Ayé ń lọ: Àgbéyẹ̀wò Ẹkún Ọ̀ọ́rọ̀ bí Orò Ìṣípòpadà fún Abilékọ ní Ilẹ̀ Yorùbá" nínú *Láàńgbàsà (Jọ́nà Iṣẹ́ Akadá ní Èdè Yorùbá*, No 15, Lagos: Univesity of Lagos.

Dáramọ́lá, O. & Jẹ́jẹ́, A. (2014). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọn-Òjé Press.

**MÓDÙ KEJÌ**

**ÌPÍN KÌNNÍ: ÀWỌN ẸKA ÀṢÀ ÌBÍLẸ̀ ŃLÁŃLÁ YORÙBÁ**

***Àkóónú***


1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Iṣẹ́ Àgbẹ̀

4.2 Iṣẹ́ Ọdẹ: (i) Ọdẹ Igbó, (ii) Ọdẹ Apẹja

4.3 Iṣẹ́ Àgbẹ̀dẹ

44 Iṣẹ́ Ìṣègùn Ìbílẹ̀

4.5 Iṣẹ́ Aṣọ Híhun

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

A ti sọ síwájú pé àṣà àti ìṣẹ̀ṣe Yorùbá fi ara kín ara, àti pé wọ́n wọ́nu ara wọn ṣùgbọ́n o, kì í jẹ́ ti baba, tọmọ kí ó má ní ààlà. Ìṣẹ̀ṣe Yorùbá gẹ́gẹ́ bí a ti rí àwọn àpẹẹrẹ rẹ̀ díẹ̀ nínú Módù kìnní jẹ́ àwọn ìṣe àti ohun mánigbàgbé tí Yorùbá máa ń ṣe láti ṣe ìrántí àwọn gbankọgbìì ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ti wáyé lọ́jọ́ ọjọ́un, èyí tí wọ́n fi máa ń kọ́ àwọn ọmọ wọn lẹ́kọ̀ọ́ àti èrèdí tí àwọn nǹkan wọ̀nyí fi ṣẹlẹ̀.

Nínú módù kejì yìí ni a ti wo ohun tí a ń pè ní àṣà Yorùbá pọ́nńbélé tàbí àwọn ẹ̀ka àṣà Yorùbá ńláńlá tí ó ti wà ní àtètèkọ́ṣe, èyí tí ó sì ń bẹ tàbí tí wọn ń tẹ̀lé láti ìgbà ìwáṣẹ̀, títí di ìsinsinyìí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìṣẹ̀ṣe kì í sábà yí padà, àṣà máa ń pàwọ̀dà nígbà mìíràn pàápàá bí ojú bá ti ń là síi. Èyí ni pé ọ̀làjú òde òní máa ń mú kí àṣà yí padà fẹ́ẹ̀rẹ́fẹ́ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kì í parẹ́ rárá.

Ó ṣe pàtàkì láti ṣe àkíyèsì pé àṣà gbòòrò púpọ̀, nítorí pé bí a ṣe ní àwọn ẹ̀ka àṣà ńláńlá ni a tún ní àwọn ẹ̀ka àṣà kéékèèké mìíràn. Ìdí nìyí tí a kọ́kọ́ wo díẹ̀ nínú àwọn ẹ̀ka àṣà Yorùbá ńláńlá nínú Módù yìí, kí á tó lọ wo díẹ̀ nínú àwọn ẹ̀ka àṣà Yorùbá kéékèèké mìíràn nínú Módù kẹta.

Nínú Módù kejì yìí ni a ti wo àwọn ẹ̀ka àṣà bíi àṣà ọmọlúàbí, ìwọ̀ṣọ, oge ṣíṣe àṣà ìran-ara-ẹni-lọ́wọ́, ìgbéyàwó àti ìsọmọlórúkọ, iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé Yorùbá, àṣà Ìbọ̀rìṣà, eré ìdárayá ṣíṣe àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Nínú ìpín yìí ni a ti ṣe àlàyé pàtàkì iṣẹ́ àgbẹ̀ láàrín iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé Yorùbá. A ṣe ìtẹnumọ́ iṣẹ́ yìí gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ tí ó ń fún Yorùbá ní ìdánilójú ìwàláàyè ẹ̀dá. Èyí ni iṣẹ́ tí ń pèsè ohun jíjẹ́ tí ó ń so ẹ̀mí ènìyàn ró. Ṣe bí kò bá sí ebi, wàhálà ìwàláyé ẹ̀dá ènìyàn dínkù jọjọ. Ìdí ni pé kò sí àwùjọ àgbáyé kankan tí ó lè wà láàyè láìsí jíjẹ àti mímu èyí tí àwọn àgbẹ̀ máa ń pèsè. Nítorí náà, iṣẹ́ àgbẹ̀ jẹ́ iṣẹ́ tí ó gbajúgbajà láwùjọ àgbáyé.

Lẹ́yìn iṣẹ́ àgbẹ̀ ni a tọ́kasí iṣẹ́ ọdẹ igbó tàbí ọdẹ apẹja bẹ́ẹ̀ ni iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ kò kẹ̀rẹ̀ nínú iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé Yorùbá. Iṣẹ́ mìíràn tí ó tún ṣe pàtàkì tí a mẹ́nubà ni iṣẹ́ ìṣègùn ìbílẹ̀ àti iṣẹ́ aṣọ híhun. Ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí ni a fi ìṣepàtàkì wọn hàn ní ìṣẹ̀dálẹ̀ Yorùbá.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Èròǹgbà ìdánilẹ́kọ̀ọ́ lórí iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé Yorùbá ni:

- Láti fi ìṣepàtàkì iṣẹ́ ṣíṣe hàn láàrin ẹ̀dá alààyè.
- Kí akẹ́kọ̀ọ́ lè ní ìmọ̀ iṣẹ́ ṣíṣe láàrín àwùjọ Yorùbá.
- Láti jẹ́ kí á mọ̀ pé oúnjẹ ni ó ń mú ẹ̀dá wà láàyè, kí ó sì ní ìlera pípé.
- Kí akẹ́kọ̀ọ́ àti òǹkàwé lè ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìmọ̀ nípa iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé Yorùbá kọ̀ọ̀kan.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. "Ẹni tí kò ṣiṣẹ́ kò yẹ kí ó jẹun". Dá sí ọ̀rọ̀ yìí.
2. Dárúkọ oríṣìí iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé Yorùbá márùn-ún àti ìṣepàtàkì wọn.
3. Ìlú wo ni iṣẹ́ aṣọ híhun ti gbajúmọ̀ àwùjọ Yorùbá?
4. Ǹjẹ́ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá tẹ́lẹ̀ wúlò mọ́ lóde òní?
5. Ọ̀nà wo ni àwọn Yorùbá máa ń gbà tọ́jú ìlera ara wọn láyé àtijọ́?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Iṣẹ́ Àgbẹ̀

Bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa iṣẹ́ àgbẹ̀, a níláti ṣe àkíyèsí pé iṣẹ́ yìí jẹ́ kárí-ayé nítorí pé kò sí ibi tí wọn kì í ti í kó adìẹ alẹ́ ni ọ̀rọ̀ náà jẹ́. Ní gbogbo àwùjọ ayé ni wọ́n ti ń ṣe iṣẹ́ àgbẹ̀, ṣùgbọ́n ṣá o, ìyàtọ̀ bí a ṣe ń ṣe é máa ń yàtọ̀ láti agbègbè kan sí òmíràn. Bí kò bá sí tàǹgíìrì, awọ kò le hu ni ọ̀rọ̀ iṣẹ́ àgbẹ̀ jẹ́ nítorí àwọn àgbẹ̀ ni ó máa ń pèsè oúnjẹ fún ẹ̀dá ènìyàn àti àwọn ẹran ọ̀sìn. Nítorí pé àwọn wọ̀nyí ni kì í jẹ́ kí ebi pa ẹ̀dá ènìyàn.

Ní àwùjọ Yorùbá, iṣẹ́ àgbẹ̀ jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn iṣẹ́ tí ó pàtàkì jùlọ nítorí pé ebi kì í wọnú, kí ọ̀rọ̀ mìíràn wọ̀ ọ́. Nítorí náà, iṣẹ́ àgbẹ̀ jẹ́ iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé tí ó gbajúgbajà.

A lè pín iṣẹ́ àgbẹ̀ sí ẹ̀ka méjì; (i) ẹ̀ka iṣẹ́ àgbẹ̀ aroko (ii) iṣẹ́ àgbẹ̀ ẹran sísin. Iṣẹ́ àgbẹ̀ aroko ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn yàn láàyò púpọ̀ jù nítorí àwọn àgbẹ̀ aroko ni wọ́n máa ń gbin gbogbo ohun tí ẹnu ń jẹ, èyí tí ó ń fún ara lókun àti ìlera pípé. Lára àwọn ohun ọ̀gbìn ni àgbàdo, ẹ̀wà, iṣu àti ẹ̀gẹ́. Àwọn ohun ọ̀gbìn jíjẹ̀ yìí tún pín sí onírúurú ẹ̀yà wọn. Bí àpẹẹrẹ, àgbàdo ògì àti ọkà bàbà. Bẹ́ẹ̀ ni lára àwọn irúfẹ́ ẹ̀wà ni a ti rí ẹ̀wà erèé, ẹ̀wà awújẹ, ẹ̀wà àti sèsé. Iṣu náà ní onírúurú tiwọn. Nínú wọn ni a ti rí iṣukọ tí a fi ń gúnyán tàbí jẹ níṣu, a tún rí iṣu ewùrà àti iṣu èsúrú fún jíjẹ. Iṣu kókò àti iṣu ànàmọ́ náà wà fún jíjẹ, nígbà tí a rí iṣu ẹ̀gẹ́ tí wọ́n fi ń ṣe èlùbọ́ láfún tàbí ṣe gàrí. Yàtọ̀ sí iṣu ẹ̀gẹ́ tí a fi ń ṣe èlùbọ́ láfún, irúfẹ́ iṣu ẹ̀gẹ́ kan tún wà tí wọ́n máa ń jẹ níṣu. Èyí ní àwọn Yorùbá máa ń pè ní *'Iṣu-nìkàn-kíyán"*.

Àwọn àgbẹ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá tún máa ń gbin àwọn igi owó mìíràn bíi kòkó, obì, ọ̀pẹ àti àgbọn. Èso àgbọn yìí wúlò púpọ̀ fún ètò ìlera ẹ̀dá nínú àgọ́ ara. Àwọn igi owó wọ̀nyí ni wọ́n máa ń fi èso wọn ṣọwọ́ sí ilẹ̀ òkèèrè láti gba owó gege fún orílẹ̀-èdè tàbí àwùjọ wa.

Ní ti iṣẹ́ àgbẹ̀ ẹranko sísìn, Yorùbá máa ń sin àwọn ẹran ọ̀sìn bíi ewúrẹ́, àgùntàn, ajá, adìẹ, tòlótòló àti ológbò. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n máa ń sin àwọn ẹran ọ̀sìn wọ̀nyí fún pípajẹ ni, ajá àti ológbò ni wọ́n máa ńlò fún ìdáàbò bo ilé àti láti fi wọ́n ṣe ọdẹ.

## 4.2 Iṣẹ́ Ọdẹ

Lára àwọn iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé Yorùbá ni iṣẹ́ ọdẹ wà. Ọ̀nà mẹ́ta ni a lè pín iṣẹ́ ọdẹ sí: (i) Ọdẹ igbó àti ọ̀dan, (ii) Ọdẹ Odò (iii) Ọdẹ Ìlú.

### *(i) Ọdẹ Igbó/Ọ̀dan*

Àwọn tí ń ṣọdẹ igbó àti ọ̀dàn ni àwọn ọdẹ tí wọ́n máa ń pa ẹranko fún títà àti jíjẹ fún ìgbáyégbádùn àwọn ará ìlú. Wọ́n máa ń ṣọdẹ ẹranko nínú igbó kìjikìji bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń ṣọdẹ nínú pàlàpálá inú ọ̀dàn nítorí pé àwọn ẹranko tí ó máa ń gbé inú igbó yàtọ̀ sí àwọn ẹranko tí ń gbé inú ọ̀dàn. Bí àpẹẹrẹ, àwọn ẹranko bíi kìnnìún, erin, àmọ̀tẹ́kùn, ẹkùn, ìgalà, ẹfọ̀n, jàkùmọ̀, túrùpú (ẹlẹ́dẹ̀ ẹgàn) èsúró sábà máa ń gbé nínú Igbó ńlá nígbà tí àwọn ẹranko bíi ẹtu, ọ̀yà, kúnnúgbá, ikún àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ máa ń sábà

wà nínú ọ̀dàn. Àwọn irúfẹ́ ọdẹ yìí ni wọ́n máa ń dẹ inú igbó àti ọ̀dàn láti le rí ẹran pa fún àwọn ará ìlú.

Àwọn ọdẹ wọ̀nyí máa ń ní onírúurú irin-iṣẹ́ tí wọ́n máa ń lò fún iṣẹ́ ọdẹ ṣíṣe wọn. Díẹ̀ nínú àwọn irin-iṣẹ́ wọ̀nyí ni àdá, ìbọn, ọfà, pàkúté àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ní pàtàkì jùlọ, ọdẹ adẹgbó àti ọdẹ adẹ-ọ̀dàm gbọ́dọ̀ ní àwọn oògùn tí ó gbórín nítorí àwọn ẹranko abìjà máa ń pọ̀ nínú igbó àti ọ̀dàn. Ìdí nìyí tí a ṣe máa ń gbọ́ pé;

> Ọdẹ tí yóò perin,
> Kó tọjú egbé
> Èyí tí yóò pẹfọ̀n
> Kó tọ́jú àjàbò
> Ọdẹ tí yóò pa túùpú,
> Kí ó má sàfira ojúgun.

Àwọn ọdẹ wọ̀nyí máa ní lò òògùn bí àfẹ́ẹ̀rí, egbé àti ọfọ̀. Èyí ni wọ́n fi máa ń gba ara wọn sílẹ̀ lọ́wọ́ àwọn ẹranko abìjà. Èyí túmọ̀ sí pé ọdẹ tí yóò lọ sínú igbó lọ sọdẹ níláti jẹ́ ogbójú ọdẹ tí ó ní òògùn abẹnu gọ̀ngọ̀.

### *(ii) Ọdẹ Adedò*

Yàtọ̀ sí àwọn ọdẹ igbó àti ọdẹ ọ̀dàn yìí, a tún máa ń rí àwọn ọdẹ adẹdò, tí wọ́n máa ń ṣe ọdẹ tiwọn nínú tàbí létí omi. A ó rí i pé yàtọ̀ sí àwọn ẹja ńláńlá tí ó wà nínú ibú, àwọn ẹranko kan tún wà tí wọ́n fi inú omi ṣe ibùgbé wọn. Lára wọn ni erinmilókun, àrọ̀gìdìgbà, olúfà, erè àti àwọn ẹja ńláńlá mìíràn tí títóbi wọn ju ti ẹranko igbó mìíràn lọ. Ṣùgbọ́n sá o, ibi tí wọ́n bá ti ní odò ńlá ni àwọn ọdẹ adẹdò yìí sábà máa ń pọ̀ sí. Bí àpẹẹrẹ, yàtọ̀ sí àwọn agbègbè tí òkun àti ọ̀sà wà ní Ilẹ̀ Yorùbá, a tún ní àwọn odò ńlá bíi Odò Ọ̀ṣun, Ògùn, Ṣaṣàá, Ọbà àti àwọn odò mìíràn káàkiri Ilẹ̀ Yorùbá, nínú èyí ti onírúurú ẹja ńlá àti ẹja kéékèèkéé wà; bẹ́ẹ̀ ni ọ̀pọ̀ ejò afàyàfà ni wọ́n wà nínú àwọn omi wọ̀nyí.

### *(iii) Ọdẹ Ìlú/Ọdẹ Asọ́lùú (fún ààbò ìlú)*

Àwọn ọdẹ wúlò púpọ̀ ní àwùjọ Yorùbá nítorí pé àwọn ni Ìlú máa ń lò fún ìdáàbò bo àwọn ènìyàn bẹ́ẹ̀ ni àwọn ọdẹ ni wọ́n máa ń kojú ogun nígbàkìgbà tí àwọn ọ̀ta bá gbógun dé. Ìdí nìyí tí ẹnu àwọn ọdẹ ṣe sábà máa ń ranlẹ̀ láàrín ìlú, tí gbogbo Ìlú sì máa ń fún wọn lọ́wọ̀ fún ìbẹ̀rù agbára òògùn tí wọ́n máa ń ní. Ìdí niyí tí Yorùbá ṣe

máa ń sọ pé *"Ẹni tó gbàyàwó ọdẹ, kò jìnnà síkú, bẹ́ẹ̀ ni ikú kò jìnnà sí ẹni ọdẹ́ gbà lóbìnrin"*. Wàyí ò, bí iṣẹ́ ọdẹ ti ṣe pàtàkì tó yìí, àwọn ọdẹ tún máa ń ṣíṣe àgbẹ̀ mọ́ iṣẹ́ wọn, níwọ̀n bí ó ṣe ṣe pàtàkì pé oúnjẹ ni ó máa ń mú ẹ̀mí ró.

Lóde òní, ó ṣeni láàánú pé ìyípadà díẹ̀ ti dé bá iṣẹ́ ọdẹ ní àwùjọ Yorùbá. Bí àpẹẹrẹ, gbogbo igbó ni ọdẹ máa ń dẹ láyé àtijọ́, ṣùgbọ́n lóde òní, a ti ya àwọn igbó kan sọ́tọ̀ gẹ́gẹ́ bí *"Igbó Ọba"*, èyí tí ẹnikẹ́ni kò le kù gìrì wọ̀ láìgba ìwé àṣẹ láti ṣe bẹ́ẹ̀ yálà fún ọdẹ ṣíṣe tàbí nǹkan mìíràn, bẹ́ẹ̀ ni o lójú irú ẹranko tí ọdẹ lè pa nínú igbó ọbá yìí àti pé ó ní àsìkò tí wọ́n lè wọ inú igbó náà. Wàyí ó, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé iṣẹ́ ọdẹ síṣe ṣe pàtàkì lóde òní, ofin ìjọba ti ká wọn lọ́wọ́ kò láti ṣe ohun tí ó bá wu ọdẹ nínú igbó.

## 4.3 Iṣẹ́ Àgbẹ̀dẹ Ògún

Bí a bá ṣe àtúpalẹ̀ ọ̀rọ̀ tí a pè ní *'àgbẹ̀dẹ'*, a ó ṣe àkíyèsí pé ọ̀rọ̀ méjì ni a papọ̀ di ọ̀kan níbí. Àwọn ọ̀rọ̀ méjì náà ni *"Àgbẹ̀"* àti *"Ọdẹ"*, èyí tí a ti mẹ́nubà ní òkè yìí. A ti ṣe àlàyé nípa ohun tí àwọn àgbẹ̀ àti àwọn ọdẹ ń ṣe gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé Yorùbá àti ìṣepàtàkì iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan yìí ní ìgbé-ayé àwọn Yorùbá.

Nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ iṣẹ́ *'àgbẹ̀dẹ'*, a ó rí i pé àgbẹ̀ àti ọdẹ ni a kó papọ̀ tí ó di *'àgbẹ̀dẹ'* nípa ìlànà ìpajẹ àti ìsúnkì. Èyí ni pé, a pa *'Ọ'* tí ó bẹ̀rẹ̀ ọdẹ jẹ nígbà tí a sún ọ̀rọ̀ méjèèjì náà papọ̀ tí ó wá di àgbẹ̀dẹ. Èyí ni *àgbẹ̀ + (ọ)dẹ* = Àgbẹ̀dẹ.

A má ń tọ́ka sí iṣẹ́ yìí gẹ́gẹ́ bí Àgbẹ̀dẹ Ògún nítorí pé Yorùbá gbàgbọ́ pé Òrìṣà Ògún ni alágbẹ̀dẹ àkọ́kọ́. Àwọn alágbẹ̀dẹ Ògún ni wọ́n máa ń rọ àwọn ohun èlò tí àwọn àgbẹ̀ àti àwọn ọdẹ máa ń lò gẹ́gẹ́ bí irin-iṣẹ́ wọn. Lára àwọn irin-iṣẹ́ àgbẹ̀ aroko àti apẹja ni a ti rí àdá, ọkọ́, ọ̀bẹ, tí àwọn ọdẹ sì máa ń lo àdá, ìbọn, ọ̀kọ̀, idà àti àwọn ohun ìjà mìíràn fún ẹranko pípa tàbí fún ogun jíjà. Èyí túmò sí pé iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ Ògún ni ó máa ń pèsè irin-iṣẹ́ fún àgbẹ̀ àti àwọn ọdẹ. Nítorí náà, a lè sọ pé bí kò bá sí àgbẹ̀dẹ, àwọn àgbẹ̀ àti àwọn ọdẹ kò bá ní ìṣòro díẹ̀ nípa ìjáfáfá iṣẹ́ wọn. Bí àwọn àgbẹ̀ ṣe ń lo ọkọ́ bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ń lo àdá, àti ọkọ́ fún oko ríro tàbí ilẹ̀ sísán, tí wọ́n sì máa ń lo dòjé láti fi kórè oko wọn. Ní ti àwọn ọdẹ wàyí ò, wọ́n máa ń lo ìbọn, àdá, ọ̀bẹ, ọ̀kọ̀, tàkúté àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nípa ìdí èyí, a ó rí i pé bí kò sí tàǹgíìrì, awọ kò leè hu ni ọ̀rọ̀ iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ jẹ́ fún àwọn àgbẹ̀ àti àwọn ọdẹ.

## 4.4 Iṣẹ́ Ìṣègùn Ìbílẹ̀

Ọ̀kan pàtàkì nínú iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé pàtàkì ni iṣẹ́ ìṣègùn ìbílẹ̀ jẹ́ láàrín àwọn Yorùbá. Yorùbá bọ̀, wọ́n ni *"kí àgbàdo tó dáyé, nǹkan kan ni adìẹ ń jẹ"*. Èyí túmọ̀ sí pé kí àwọn òyìnbó aláwọ̀ funfun tó dé sí àwùjọ Yorùbá ni àwọn babańlá wọ́n tí ń ṣe ìwòsàn fún àwọn ènìyàn wọn, lọ́nà ti ìbílẹ̀. Èyí ni pé Yorùbá ti ń lo ewé àti egbò fún ìwòsàn ara wọn láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Nípa àkíyèsí àyíká ẹni, wọ́n mọ ewé àti egbò tí ó lè mú àìsàn lọ àti èyí tí ó lè wúlò fún àtidènà àìsàn. Nípa báyìí, àwọn ló ń ṣíṣẹ ìṣègùn ìbílẹ̀ àti bí a ṣe ń tọjú onírúurú àìsàn tí ń bá ẹ̀dá ènìyàn àti ẹranko jà. Gẹ́gẹ́ bí Agbáje (1989) ṣe sọ, àwọn wọ̀nyí ló máa ń tọ́jú àwọn aláìsàn, aláboyún àti àwọn tó ń rawọ́ ẹ̀bẹ̀ sí Èdùmàrè fún ìpèsè ọmọ. Yàtọ̀ sí èyí, àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ wọ̀nyí ni ó máa ń tọ́jú ẹni tí àkeekèè bá ta tàbí àwọn tí ejò bá bù sán. Àwọn wọ̀nyí ni ó máa ń to eegun àwọn tó bá jábọ́ lórí ọ̀pẹ tàbí igi gíga tí wọ́n bá kan léegun tàbí tí wọ́n bá fi orí gbálẹ̀.

Níwọ̀n ìgbà tí Yorùbá ti gbà pé ara kì í ṣe òkúta, wọ́n máa ń múra sílẹ̀ fún oríṣìíríṣìí àjálù àìsàn tí ó lè fẹ́ẹ́ yọjú láti kó àgọ́ ara sí wàhálà. Wọ́n gbà pé ìlera lọrọ̀ àti pé ẹni tó bá ní àlàáfíà, ó ní ohun gbogbo. Nítorí náà, bí onírúurú ìpèníjà àìsàn bá ṣẹ́yọ, ìbáa ṣe lórí ìtọjú aláboyún àti ọmọ bíbí, ìtọ́jú ọmọdé, àìsàn aromọléegun, inú rírun tàbí orí fífọ́, akọ ibà tàbí tápà, àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ yìí ni yóò ṣe ìtọ́jú irúfẹ́ aláìsàn bẹ́ẹ̀. Síwájú sí i, àwọn oníṣẹ̀gùn ìbílẹ̀ yìí máa ń tọ́jú àrùn ọpọlọ àti àwọn àìsàn tó bá jẹ mọ́ ẹ̀mí àìrí. Wọ́n yóò ṣe ìwádìí ohun tí ó fa irúfẹ́ àrùn bẹ́ẹ̀ lọ́wọ́ àwọn irúnmọlẹ̀, pàápàáa jùlọ lọ́wọ́ Ọ̀rúnmìlà, èyí tí í ṣe akéréfinú-ṣọgbọ́n, akọ́nilọ́ràn bí ìyekan ẹni, òpìtàn Ilẹ̀-Ifẹ̀. Akò ní í sàìmẹ́nubà á pé òrìṣà **Ọ̀sanyìn ni** ó wà fún ìṣègùn ìbílẹ̀ Yorùbá. Ọ̀ṣanyìn yìí jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ọ̀kànlénú irúnmọlẹ̀ tí ó rọ̀ láti ìsàlú ọ̀run wá sí òde ìsálayé ní ìgbà ìwásẹ̀. Ó súnmọ́ Ọ̀rúnmìlà pẹ́kípẹ́kí nítorí ìmọ̀ tí ó ní nípa ewé àti egbò, oun ni ó sì máa ń ṣe amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ fún Ọ̀rúnmìlà nígbà náà. Ìtàn kan tilẹ̀ sọ pé nígbà kan tí Ọ̀rúnmìlà rán Ọ̀sanyìn láti lọ bá a sán oko, ńṣe ni Ọ̀sanyìn sọ fún un pé nígbà tí òun dé oko náà, kò sí ewé tí òun lè gé dànù nítorí pé gbogbo àwọn ewé wọ̀nyí ló wúlò fún oògùn. Nítorí náà, Ọ̀rúnmìlà ní kí ó máa dúró ti òun fún iṣẹ́ ìwòsàn. Òun ni ó mọ̀ nípa ewé àti egbò, tí ó sì jẹ́ olùdámọ̀ràn fún Ọ̀rúnmìlà lórí ìwòsàn àti ìlera ènìyàn.

Wàyí ò, ó ṣeni láàánú pé nígbà tí àwọn ẹ̀sìn àtọ̀húnrìnwá dé ilẹ̀ Yorùbá pẹ̀lú ìlànà àti ètò ìwòsàn wọn, wọ́n fi ẹnu tẹ́ḿbẹ́lú ètò ìwòsàn àti ìṣègùn ìbílẹ̀ Yorùbá láti mú un di yẹpẹrẹ. Ṣùgbọ́n sá, pípa tí wọ́n ń pa èèpo osè, ara ni ó fi ń san. Bí o tilẹ̀ jẹ́ pé

ọ̀pọ̀ àwọn alákọ̀wé ọmọ Yorùbá gba ẹ̀sìn sódì, tí wọ́n kò kọbi ara sí lílo òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá mọ́, a rí i pé iná ilé ni ọmọ ehoro wọn ń yá gbẹ̀yìn nítorí pé ọ̀pọ̀ wọn ni ó padà sí lílo òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá lónìí, tí wọn kò sì fi gbogbo ara gbé òògùn òyìnbó lárugẹ mọ́ nítorí ọwọ́ gege tó gbé karí, àti pé ó lójú àwọn àìsàn kan tí òògùn Òyìnbó kò lè wò, àfi òògùn ìbílẹ̀.

Àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ Yorùbá náà ti ń ṣe gudugudu méje, yààyàà mẹ́fà láti fi hàn pé òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá pedegé, ó fi gbọ̀ọ̀rọ̀ jẹka.

## 4.5 Iṣẹ́ Aṣọ Híhun

Ní àtètèkọ́ṣe ni ẹ̀dá ènìyàn ti ń gbìyànjú láti fi nǹkan bo àṣírí ara wọn. Ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, àwọn àwùjọ kan máa ń fi ewé bora, ṣùgbọ́n nígbà tí ọ̀làjú dé, àwọn nǹkan tí ènìyàn fi ń bo àṣírí ara wọn kúrò ní à ń lo ewé tàbí awọ ẹranko. Àwọn ènìyàn ní ìmọ̀ nípa òwú tí a lè lò láti le hun aṣọ tí yóò mú kí ara wọn dùn ún wò dáradára. Ní gbogbo àwùjọ àgbáyé, kò sí ẹ̀dá ènìyan kan tí wọn kò ní ọ̀nà àti ìmọ̀ lórí ìdáàbò bo ara ẹni nípa aṣọ wíwọ̀. Ní òde-òní, oníkálukú orílẹ̀-èdè ló ni aṣọ tí wọ́n máa ń wọ̀, èyí sì jẹ mọ́ irúfẹ́ agbègbè tí Olódùmarè dá wọn sí. Àwọn mìíràn ní ilẹ̀ otútù níbi tí ilẹ̀ ibẹ̀ tutù rinrin nígbà tí a da àwọn ènìyàn mìíràn sí ilẹ̀ olóoru níbí tí ilẹ̀ ibẹ̀ gbé gbóná janjan. Èyí ni ó fa ọ̀kan-ò-jọ̀kan aṣọ tí a máa ń wọ̀ láti agbègbè kan sí òmíràn.

Ní àwùjọ Yorùbá tí Olódùmarè ṣẹ̀dá sí ilẹ̀ olooru, a rí i pé oríṣìíríṣìí aṣọ tí ó jẹ mọ ibi tí a dá wọn sí ni a ń rí. Nígbà tí ọjọ́ ń gorí ọjọ́, tí ìmọ̀ sì ń yí lu ìmọ̀, Yorùbá bẹ̀rẹ̀ sí í ní ìmọ̀ nípa òwú gbígbìn, wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí hun aṣọ tí ó bá òde mu. Ní agbègbè kan tí a ń pè ní Ìṣẹ́yìn ní apá Òkè-ògùn Ilẹ̀ Yorùbá, òwú gbígbìn yìí jẹ́ iṣẹ́ pàtàkì fún wọn, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n bẹ̀rẹ̀ si í hun aṣọ ìbílẹ̀ kan tí a mọ̀ sí *"Aṣọ Òfì"*. Aṣọ òfì yìí gbajúmọ̀ káàkiri Ilẹ̀ Yorùbá bẹ́ẹ̀ ni aṣọ yìí ni wọ́n sábà máa ń lò fún ayẹyẹ ìgbéyàwó àti oyè jíjẹ ní tìbú tòòrò ilẹ̀ Yorùbá. Títí di òní olónìí, aṣọ òfì kò kẹ̀rẹ̀ láàrín àwọn gbajúmọ̀ aṣọ ilẹ̀ Yorùbá. Àwọn òyìnbó aláwọ̀ funfun náà tilẹ̀ gba ti aṣọ òfì yìí, tí wọ́n sì fi ń rán onírúurú bátànì. Ìlú Ìṣẹ́yìn yìí jẹ́ orírun ibi tí wọ́n ti ń hun aṣọ òfì, bẹ́ẹ̀ ni àwọn ahunṣọ òfì ìlú Ìṣẹ́yìn tí gbé iṣẹ́ aṣọ híhun yìí kọ́ja ìlú náà, wọ́n sì ti ń lọ hun un ní Ìlú ńlá mìíràn bí Ìbàdàn, Èkó, Abẹ́òkúta àti Ọ̀yọ́. Aṣọ òfì yìí gbajúgbajà débi pé a máa ń kọ ọ́ lórin pé;

A ránmọ láṣọ
Ìṣẹ́yìn ni ò hunṣọ
A ránmọ láṣọ
Ìṣẹ́yìn ni ò hunṣọ……

## 5.0 Ìsọníṣókí

Iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé Yorùbá ni a gbìyànjú láti mẹ́nubà nínú ìpín yìí, bẹ́ẹ̀ ni a ṣe àlàyé ìdí tí àwọn iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan yìí fi ṣe pàtàkì ní àwùjọ Yorùbá. A wo iṣẹ́ àgbẹ̀ gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ tí ó máa ń fún àwọn ènìyàn yìí ní oúnjẹ tí ó dára fún okun àti agbára pẹ̀lú ìlera pípé nígbà tí a ṣe àlàyé bí iṣẹ́ ọdẹ ṣe jẹ́ èyí tí ó ń ṣètò ààbò fún àwọn olùgbé àwùjọ Yorùbá.Níbí ni a ti jẹ́ kí á mọ̀ bí iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ ṣe wúlò fún àwọn àgbẹ̀ àti àwọn ọdẹ gẹ́gẹ́ bí irin-iṣẹ́ wọn. Lẹ́yìn èyí ni a tọ́kasí iṣẹ́ ìṣègùn ìbílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ tí Yorùbá máa ń ṣe láti tọ́jú irúfẹ́ àìsàn tí ó bá yọjú láàrín wọn, ìbáà ṣe àìsàn ara tàbí ti ẹ̀mí àìrí. Iṣẹ́ aṣọ híhun kò gbẹ́yìn nínú àwọn iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé tí a mẹ́nubà, bẹ́ẹ̀ ni a rí iṣẹ́ yìí gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ tí ń dáàbò bo àgọ́ ara, tí ó sì ń mú kí àwọ̀ ara wà ní ìpamọ́. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn oríṣìí iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé Yorùbá pọ̀ jàǹtirẹrẹ, díẹ̀ ni a lè mẹ́nubà nínú àkọsílẹ̀ yìí. Nínú àwọn iṣẹ́ ìbílẹ̀ Yorùbá tí a kò lè mẹ́nubà nínú ìwé yìí ni iṣẹ́ epo fífọ̀, iṣẹ́ ọtí pípọn àti ẹmu dídá, iṣẹ́ ohùn pípè, iṣẹ́ alápatà, iṣẹ́ ìkòkò mímọ, iṣẹ́ irin wíwà, iṣẹ́ ẹní híhun àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. A ó máa rí àlàyé nípa àwọn iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé Yorùbá wọ̀nyí lẹ́kùn-únrẹ́rẹ́ nínú àwọn ìwé mìíràn.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Dárúkọ àwọn iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé mẹ́fà tí o mọ̀.
2. Ìlú wo ni a ti ń hun aṣọ òfì ní ilẹ̀ Yorùbá?
3. Ṣàlàyé ìtúpalẹ̀ *'àgbẹ̀dẹ'* kí o sì sọ ìwúlò iṣẹ́ yìí ní àwùjọ Yorùbá.
4. Kín ni ìyàtọ̀ àti ìjọra tí ó wà láàrín ọdẹ adẹgbó àti ọdẹ apẹja?
5. "Bí kò sí tàǹgíìrì, àwọ kò leè hu ni iṣẹ́ àgbẹ̀ jẹ́ fún ìgbáyégbádùn ènìyàn àwùjọ Yorùbá". Dá sí ọ̀rọ̀ yìí.
6. Dárúkọ iṣẹ́ ìbílẹ̀ Yorùbá márùn-ún àti àwọn òrìṣà tí ó jẹ mọ́ iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan.
7. Dárúkọ àwọn ẹranko abìjà márùn-ún àti àwọn ọ̀nà tí ọdẹ máa ń gbà kápá wọn.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Daramọla, O. àti Jẹ́jẹ́, A. (1968). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn, Oníbọn-òjé Press and Book Industries (Nig.) Ltd.

Ilésanmí (ed) (1989). *Iṣẹ́ Ìṣẹ̀yìnbáyé*. Ilé-Ifẹ́, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press Ltd.

Ládélé, T.A.A. *et al* (1986). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*. Ìbàdàn, Gavima Press Ltd.

Zaslavsky, C. (1973). *Africa Counts*. Boston Massachusatts, Lawrence Hill and Company.

Adéwálé, G.O. (2005). *The Role of Ìṣẹ́yìn Weaving Tradition in the Social, Cultural and Economic Development of Ọ̀yọ́ and other Yorùbá Speaking States*. Ìbàdàn, Research Centre for Arts, Culture and Communication Development.

Gbàdàmọ́sí, O.A. (2015). "The use of Herbs as an Alternative Method of Healing in Contemporary Nigerian Soceity" in *Yorùbá Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria*, vol. 8, No 1, Ìbàdàn, Yorùbá Studies Association of Nigeria.

## MÓDÙ KEJÌ

## ÌPÍN KEJÌ: ÌWÀ ỌMỌLÚÀBÍ

***Àkóónú***

1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́: *Àwọn Àwòmọ́ Ìwà Ọmọlúàbí*

4.1 Ìkíni gẹ́gẹ́ bí ìwà ọmọlúàbí

4.2 Ìbọ̀wọ̀ fúna Àgbà

4.3 Ìhùwàsí àti Ìgbé-ayé

44 Iṣẹ́ Ṣíṣe

4.5 Ipò tí àṣà àti Ìwà Ọmọlúàbí wà lónìí

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Ìwà ọmọlúàbí tọ́ka sí ẹni tí a bíire, tí ẹni rere tọ́ dàgbà tí òun pẹ̀lú sì jẹ́ ẹni rere. Ìlànà jíjẹ́ ọmọlúàbí ní òténté ọgbọ́n ìtáyéṣe àti ìgbésí ayé àlàáfíà tí àwọn bàbáńlá wa gbé kalẹ̀. A máa ń rí ìwà ọmọlúàbí nínú ìhùwàsí, ìṣesí, ìpèdè àti ìdáhùn sí ìbéèrè.

Láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ni àwọn Yorùbá ti ka ìwà ọmọlúàbí sí ohun kan gbòógì tí ó lè mú kí àwùjọ wọn ní ìdàgbàsókè, àlàáfíà àti ìfọkànbalẹ̀. Nítorí náà, wọ́n gbà pé ìwà ọmọlúàbí jẹ́ àmúyẹ tí ó lè sin àwùjọ náà dé èbúté ògo. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń kọ́ àwọn ọmọ wọn ní ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí èyí tí yóò mú kí wọ́n dàgbà lẹ́mì-ín àti lára ní àwùjọ wọn.

Gbogbo àwọn ìwà ọmọlúàbí tí ó jẹ mọ́ ìhùwàsí, òtítọ́ sísọ àti síṣe, ìfaradà, sùúrù, àlejò síṣe ni a gbéyẹ̀wò níbí, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ohun àmúyẹ fún ìdàgbàsókè àti àlàáfáà àwùjọ wa yìí ti ń yí padà, èyí tí ó sì ń fa ìkùnà àti ìdènà fún ìlọsíwájú, ààbò àti àlàáfíà ààrin àwùjọ. Síbẹ̀síbẹ̀, kò sí bí a ó ṣe dé igbá osùn tí a kò ní í bá díẹ̀ tí a ó fi pa ọmọ lára. Ìwà ọmọlúàbí sì wà láàrin àwọn péréte ọmọ Yorùbá, ní pàápàá jùlọ díẹ̀ nínú àwọn májẹ̀ẹ̀kóbàjẹ́ àwọn àgbà gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ àwọn àgbà tí ó sọ pé *"àgbà kò gbọdọ̀ wà nílùú kí ìlú bàjẹ́"* bẹ̀ẹ̀ ni àgbà kò gbọdọ̀ wà lọ́jà kí orí ọmọ tuntun wọ́.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Àfojúsùn tàbí èròngbà ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni pé:

- Kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tàbí òǹkàwé yìí lè ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìmọ̀ nípa ìhùwàsí àtí àwọn ìwà ọmọlúàbí tí ń mú àwùjọ ní ìdàgbàsókè àti àlàáfíà.
- Kí ó lè jẹ́ ìtọ́sọ́nà fún àwọn ọ̀dọ́ ọ̀nà tí a lè gbà mú kí ààbò tó péye wà fún àwùjọ.
- Kí àwọn àgbà pàápàá lè tọ́ àwọn ọ̀dọ́ àti àwọn àgbà kàn-ǹda àwùjọ Yorùbá sí ọ̀nà rere.
- Kí àlàáfíà tí ìwà ọmọlúàbí máa ń mú wà le padà sí àwùjọ Yorùbá.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Kín ni a ń pè ní ìwà ọmọlúàbí láàrín Yorùbá?
2. Àwọn ọ̀nà wo ni a lè gbà kọ́ àwọn ọ̀dọ́ ní ìwà ọmọlúàbí lóde òní?
3. Kín ni ń fa ètò ààbò àwùjọ Yorùbá sẹ́yìn lóde òní?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìkíni gẹ́gẹ́ bí ìwà ọmọlúàbí

Ìkíni jẹ́ ọ̀kan pàtàkì ní ìwà ọmọlúàbí láàrin àwọn Yorùbá ní ayé àtijọ́. Ní ìdọ̀bálẹ̀ ni àwọn ọmọdékùnrín máa ń ki baba, ìyá àti ẹ̀gbọ́n wọn láyé àtijọ́, èyí tí kò wọ́pọ̀ mọ́ lóde òní nítorí ọ̀làjú ilẹ̀ òkèèrè tí ó gbòde kan. Lọ́jọ́ ọjọ́un, ègún burúkú ní ọmọdé tí ó bá nawọ́ sí baba tàbí ẹ̀gbọ́n rẹ̀ ń fà lé ara rẹ̀ lórí, bẹ́ẹ̀ ni ọ̀dọ́mọbìnrin tí ó jí ní àárọ̀ tí kò kúnlẹ̀ kí baba àti ìyá rẹ̀ le má gba ìre ọjọ́ náà nítorí àìmọ̀wàáhù rẹ̀.

Onírúurú àkókò ni ìkíni wà fún, bẹ́ẹ̀ ni ẹnikọ̀ọ̀kan àti oníṣẹ́ kọ̀ọ̀kan ló ní ìlànà ìkíni tiwọn. Bí àpẹẹrẹ, a lè kí ara wa ní àsìkò ọdún pé *"ẹ kú ọdún, ẹmi yóò ṣe ọ̀pọ̀ rẹ̀"*. Bí ó bá jẹ́ ẹni tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ bímọ tuntun ni, a lè kí wọn pé *"ẹ kú ewu ọmọ, Ọlọ́run yóò dá a sí o, ọ̀tun mìíràn yóò kún un o, ẹ kú ọwọ́ lómi o"*.

Ní àkókò ìbànújẹ́ ẹ̀wẹ̀, Yorùbá máa ń kí ara wọn láti tu ara wọn nínú, bẹ́ẹ̀ ni bí ó bá jẹ́ àkókò ayọ̀ ni, Yorùbá máa ń fi ìdùnnú kí àwọn ènìyàn láti bá wọn yọ ayọ̀ bẹ́ẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ síwájú, ó jẹ́ àṣà àwọn Yorùbá láti máa kí oníṣẹ́ kọ̀ọ̀kan ní ìlànà iṣẹ́ rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, wọ́n máa ń kí àwọn àgbẹ̀ pé *"àrokobọ́dúndé o"* nígbà tí wọ́n yóò kí àwọn ọdẹ pé *"àrèpa o"* Ògún á fi ọwọ́ jóná o, ọwọ́ á dẹ, o àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, tí àwọn alágbẹ̀dẹ, wọn máa ń kí wọn pé *"Àrọyè o"*. Ìkíni yìí wà fún iṣẹ́ ajé kọ̀ọ̀kan láti fi hàn pé wọ́n mọ àṣà, wọ́n sì ń gbé àṣà àbínibí wọn lárugẹ. Ṣùgbọ́n ó ṣeni láàánú pé àṣà ìkíni yìí kò fẹsẹ̀ múlẹ̀ tóbẹ́ẹ̀ mọ́ nítorí pé ọ̀làjú ti gbayé kan, bẹ́ẹ̀ ni ọ̀pọ̀ àwọn ọ̀dọ́ Yorùbá ti ń dorí àṣà yìí kodò.

## 4.2 Ìbọ̀wọ̀ fún Àgbà

Láyé àtijọ́, àṣà ìbọ̀wọ̀ fún àgbà ṣe pàtàkì, ó sì fí ìdí múlẹ̀ dan-in-dan-in. Wọ́n yóò ti kọ́ àwọn ọ̀dọ́mọdé láti máa fún àwọn àgbà ní ọ̀wọ̀ kí àwọn náà le di àgbà dáadáa ní ọjọ́ ọ̀la wọn.

Kì í ṣe baba àti ìyá nìkan ni àwọn ọmọdé gbọ́dọ̀ bọ̀wọ̀ fún. Wọ́n níláti bọ̀wọ̀ fún gbogbo àwọn tí ó bá jù wọ́n lọ. A gbọ́dọ̀ ṣe àkíyèsí pé àjùlọ yìí kò pin sí ìbikan. A gbọ́dọ̀ bọ̀wọ̀ fún ọjọ́ orí, àti ipò tí ènìyàn bá wà ní àwùjọ Yorùbá. Bí àpẹẹrẹ, tọmọdé tàgbà ló gbọdọ̀ bọ̀wọ̀ fún ọba ìlú, bóyá ọmọdé ni ọba bẹ́ẹ̀ tàbí àgbàlagbà. Ìdí nìyẹn tí àwọn Yorùbá ṣe máa ń sọ pé kí á bọ̀wọ̀ fún àwọn ajunilọ tí wọ́n lè fi ọwọ́ ọlá gbáni léti àti àwọn àgbà tí wọ́n le jáni ní tànmọ́-ọ̀n.

Láyé òde òní, ọmọdé tí ó bá bọ̀wọ̀ fún àgbà sábà máa ń bá ojúrere àwọn àgbà pàdé, wọ́n sì máa ń ní oore-ọ̀fẹ́ fún ẹ̀bùn pàtàkì lọ́dọ̀ wọn. Ìdí nìyí tí a ṣe máa ń gbọ́ nínú òwe Yorùbá kan tí ó sọ pé *"bí ọmọdé bá mọ ọwọ́ọ́ wẹ̀, yóò bá àgbà jẹun"*. Èyí ni pé àwọn àgbà yóò ní ìgbẹkẹ̀lé nínú irú ọmọdé bẹ́ẹ̀, wọn yóò sì fi oríṣiríṣi nǹkan àṣírí hàn án.

Bí oúnjẹ jíjẹ bá pa àgbà àti ọmọdé pọ̀ nínú àwo kan náà láyé àtijọ́, àgbà ni yóò kọ́kọ́ mú ẹran nínú àwo. Bí àgbà bá mú ẹran tán, ọmọdé ní láti fi ara balẹ̀ kí wọ́n mú ẹran tirẹ̀ lé e lọ́wọ́. Òde kò ní í pa tọmọdé tàgbà pọ̀ láyé àtijọ́, kí àgbà ru ẹrù ṣaájú, ọmọdé ni ó gbọ́dọ̀ rẹru tí àgbà yóò tẹ̀ lé e! Ó ṣení láàánú pé èyí kò rí bẹ́ẹ̀ mọ́ lóde òní nítorí pé wọ́n ti dorí àṣà kodò.

## 4.3 Ìhùwàsí àti Ìgbé-Ayé

Ìwà ẹ̀dá ènìyàn pín sí oríṣìí méjì. Bí àwọn kan ti jẹ́ oníwà rere ni àwọn kan jẹ́ oníwà búburú. Wàyí ò, ẹni tí ó bá ń hu ìwà rere ni Yorùbá máa ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí Ọmọlúàbí ènìyàn ní àwùjọ. Lára ìwà ọmọlúàbí ni iṣẹ́ àṣekára wà. Bí ènìyàn bá fẹ́ràn láti ṣiṣẹ, tí ó sì mójú tó iṣẹ́ rẹ̀, tí kò í fi iṣẹ́ ṣe ìmẹ́lẹ́ tàbí tí kò fi iṣẹ́ rẹ̀ jáfara, Yorùbá máa ń tọ́ka sí irú ẹni bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọmọlúàbí láwùjọ.

Ọ̀kan lára àmúyẹ ọmọlúàbí náa ni ìṣotítọ́. Gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ àwọn àgbà, òtítọ́ ni ó máa ń gbé orílẹ̀-èdè lékè, èyí ni ó sì máa ń fa ìlọsíwájú fún àwùjọ. Òmíràn nínú ohun tí a fi máa ń mọ ọmọlúàbí ni ìwà sùúrù àti ìpamọra. Ó jẹ́ àṣà Yorùbá láti máa fi ìwà

sùúrù kọ́ ọmọ láti kékeré. Wọ́n gbà pé sùúrù máa ń jẹ́ kí àwùjọ ní àlàáfíà. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń sọ pé sùúrù ni baba ìwà àti pé onísùúrù ni yóò jogún ayé.

Nínú ìwà ìbágbépọ̀ tí ó tún ṣe pàtàkì ní ríran òbí àti ẹnikejì lọ́wọ́ ní àwùjọ Yorùbá. Èyí ni pé ó ṣe pàtàkì láti máa ran àwọn òbí wa lọ́wọ́ láti kékeré. Ó le jẹ́ nípa iṣẹ́ ilé ṣíṣe tàbí iṣẹ́ oko. Láyé àtijọ́, a ó rí i pé àwọn Yorùbá máa ń kọ́ àwọn ọmọ wọn nípa iṣẹ́ ilé, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń mú wọn lọ sí oko láti kún wọn lọ́wọ́ nínú iṣẹ́ oko. Ní pàtàkì jùlọ, àwọn ọmọ ní láti ran àwọn òbí wọn lọ́wọ́ nígbà tí wọ́n bá ti dàgbà tàbí tí wọ́n ti dògbó, pàápàá nígbà tí agbára àwọn òbí wọ̀nyí ti dínkù láti ṣe iṣẹ́ agbára.

Ó jẹ́ àṣà Yorùbá láti máa lọ́wọ́ sí iṣẹ́ ìdàgbàsókè ìlú. Èyí ni yóò tún fi wá hàn gẹ́gẹ́ bí ọmọlúàbí ní irú àwùjọ bẹ́ẹ̀. Ẹnikẹ́ni tí kì í bá lọ́wọ́ sí iṣẹ́ ìlú kì í ṣe ọmọlúàbí rárá, bẹ́ẹ̀ ni wọn kì í fún irú ẹní bẹ́ẹ̀ ní ọ̀wọ̀ tí ó yẹ.

### 4.4 Iṣẹ́-Ajé Ṣíṣe

Iṣẹ́ jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú ohun tí ń gbé ẹ̀dá ènìyàn ró, èyí ni ó sì máa ń mú kí ẹ̀dá ènìyàn wá ọ̀nà láti rí oúnjẹ bọ́ ọkàn wọn. Èyí nìkan kọ́, iṣẹ́ tí a ń ṣe ni a fi ń gbé ìdílé ró nípa pípèsè oúnjẹ òòjọ́ fún ìdílé ẹni.

Ẹnikẹ́ni tí ó bá jẹ́ ọmọlúàbí gbọ́dọ̀ ní iṣẹ́ lọ́wọ́ kí ó le jẹ́ ẹni tí àwùjọ yóò fún ní ọ̀wọ̀ tirẹ̀, wọn kìí ka ọ̀lẹ ènìyàn sí ọmọlúàbí. Ìdí nìyí tí ìdílé tàbí ẹbí kọ̀ọ̀kan ṣe ní iṣẹ́ ìṣẹ̀yìnbáyé tiwọn. A rí àwọn ìdílé alágbẹ̀dẹ, alápatà, ọdẹ, aláṣọ híhun, onígbàjámọ̀, ọlọsẹ dúdú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, iṣẹ́ àgbẹ̀ aroko ni iṣẹ́ tí ó kárí àwùjọ Yorùbá, bẹ́ẹ̀ ni ó fẹ́rẹ̀ máa sí ìdílé tàbí ẹbí kan tí wọn kì í ṣe iṣẹ́ àgbẹ̀ nítorí pé iṣẹ́ àgbẹ̀ ni iṣẹ́ gbòógì iṣẹ́ ilẹ̀ Yorùbá.

Bí a bá wo ìṣepàtàkì iṣẹ́ ṣíṣe, a ó rí i pé iṣẹ́ ni òògùn iṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ àwọn àgbà. A tún máa ń gbọ́ pé ẹni tí kò ṣiṣẹ́, kò yẹ kí ó jẹun àti pé ọ̀lẹ tàbí aláìníṣẹ́ yóò jalè, bẹ́ẹ̀ ni olè kì í dúró ní ipò ọmọlúàbí ní àwùjọ Yorùbá. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe tọ́ka sí i níwájú, ọmọlúàbí kì í ṣe ìmẹ́lẹ́ lẹ́nu iṣẹ́.

Bí ènìyàn bá fẹ́ràn iṣẹ́ ṣíṣe, tí ó bójú tó iṣẹ́ òòjọ́ rẹ̀, tí kò sì fi jáfara, ọmọlúàbí ènìyàn ni wọn yóò máa pe irú ẹni bẹ́ẹ̀. Bí ènìyàn bá tẹpá mọ́ṣẹ́, tí ó lówó lọ́wọ́, yóò le ní oúnjẹ ànító àti àníṣẹ́kù, yóò rí owó ra aṣọ ìgbà, bẹ́ẹ̀ ni yóò rí owó kọ́lé. Bí ó bá jẹ́

ọkùnrin ni, yóò rí owó fẹ́ aya àtàtà, bẹ́ẹ̀ ni yóò rí ajé ṣe àwọn ohun rere gbogbo tí ènìyàn ń ṣe láyé. Ìdí nìyí tí akéwì Yorùbá kan ṣe sọ pé;

> Iṣẹ́ loògùn ìṣẹ́
> Iṣẹ́ la fì í dẹni gíga….

A gbọ́dọ̀ kíyèsí i pé ẹni tí ó bá lè ṣiṣẹ́ kárakára yóò ní àlàáfíà, bẹ́ẹ̀ ni ara rẹ̀ yóò le koko. Wọn kò ní í fi ojú àbùkù tàbí ojú burúkú wo ẹni bẹ́ẹ̀ ní àwùjọ. Bí ó bá ṣe iṣẹ́ ìlú ni, ọmọlúàbí kò ní í ṣe ìmẹ́lẹ́ nítorí onímẹ̀ẹ́lẹ́ ènìyàn ni ó máa ń fi ọwọ́ hẹ iṣẹ́ ní ààrin ọ̀pọ̀ ènìyàn. Ènìyàn yẹpẹrẹ àti ẹni búburú ni onímẹ̀ẹ́lẹ́ ní àwùjọ, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n le máa fura sí irú ẹní bẹ́ẹ̀ bí olè àti alápámáṣiṣẹ́. Ìdí nìyi tí àgbà akéwì kan (Adébáyọ̀ Fálétí) ṣe máa ń ké e nínú ewì rẹ̀ pé;

> Má tijú iṣẹ́ rẹ
> Ikán kì í tijú à ń mọlé
> Èèràn kìí tijú à ń lànà
> Alápàǹdẹ̀dẹ̀ kìí tijú
> À ń fò kiri ní gbangba oko
> Má tijú iṣẹ́ rẹ….
> Iṣẹ́ kì í pani
> Àìṣe rẹ̀ gan-an làbùkù.

Nítorí ìdí èyí, a ó rí i pé ọmọlúàbí ènìyàn ni a máa ń ka ẹni tí ó bá ń ṣiṣẹ́ kárakára ní àwùjọ Yorùbá sí. Ní ìparí, Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, *"èéfín nìwà, rírú ló máa ń rú"* Èyí ni pé wọ́n fi ìwà ẹ̀dá wé èéfín iná tí a kò le fi ọwọ́ tàbí igbá bò ó bí ó bá ti ń rú jáde.

## 4.5 Ipò Tí Àṣà Ọmọlúàbí Wà Lónìí

Ọ̀pọ̀ ìtàn, àrọ́bá àti àkọsílẹ̀ ló fi hàn pé ìran Yorùbá ayé ọjọ́un ní àṣà tí ó lajú àti pé èdè àti lítíréṣọ̀ ni irin-iṣẹ́ tí àwùjọ Yorùbá ń lò láti sọ àṣà, ìṣe àti ìwà ọmọlúàbí lọ́jọ̀.

Ṣùgbọ́n o, gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀ lónìí, ipò tí àṣà Ọmọlúàbí wà lónìí ti tojú súni. Ọmọlúàbí tí í ṣe àṣà àti orúkọ tí tọmọdétàgbà káràmásìkí tẹ̀lẹ̀tẹ̀lẹ̀ kò já mọ́ nǹkankan mọ́ báyìí. Gẹ́gẹ́ bí Fáléti (2009) ṣe sọ, òtítọ́, ifẹ́ ọmọnìkejì, ìkónimọ́ra, wíwá ìlọsíwájú àwùjọ àti àwọn àbùdá ọmọlúàbí báwọ̀n-ọn-nì ti pòórá. Ọ̀làjú òde-òní ti ṣe ìwà ọmọlúàbí lọ́ṣẹ́. Àpẹẹrẹ ìṣelọ́ṣẹ́ yìí hàn nínú wíwọ aṣọkáṣọ, ṣíṣe oríṣiríṣi irun àbùkù

sórí, wíwọ sòkòtò sí bẹ̀bẹ̀rẹ́ ìdí, ijó ẹlẹ́yà ní jíjó àti irúfẹ́ ìwà ìbàjẹ́ bẹ́ẹ̀ ti gbayé kan, pàápàá láàrin àwọn ọ̀dọ́ lákọlábo.

Ó ṣeni láàánú pé ọ̀làjú ilẹ̀ òkèèrè yìí kò jẹ́ ká ṣe àyẹ́sí tàbí ìpolongo ìwà àti àṣà ọmọlúàbí mọ́. Dípò bẹ́ẹ̀, jìbìtì, ọ̀kánjúà, àìṣòótọ́, wíwá owó lọ́nà àìtọ́, ṣìná ṣíṣe, ìgbénipa, ẹgbẹ òkùnkùn àti ẹgbẹ́ awo kíkó wíwọ siṣe àti àwọn ìwà burúkú bẹ́ẹ̀ ni ó gbòde kan láàrin àwọn ènìyàn àwùjọ wa, pàápàá àwọn ọ̀dọ́. Ọmọdékùnrin kò dọ̀bálẹ̀ kí baba mọ́, bẹ́ẹ̀ ni àwọn ọ̀dọ́mọdébìnrin kò kúnlẹ̀ kí ìyá mọ́. Ọ̀pọ̀ àwọn ọ̀dọ́ ìwòyí kò ran àwọn òbí lọ́wọ́ bẹ́ẹ̀ ni ìbọ̀wọ̀fágbà ti di ohun àtijọ́. Gbígba ẹ̀kọ́ ilé, ìkíni, sùúrù àti iṣẹ́-ilé ṣíṣe ti di ohun ìgbàgbé.

Ìṣọ̀lá (2009) ní tirẹ tọ́ka sí ọsẹ tí òwò ẹrú, ìjọba amúnisìn àti àwọn ẹ̀sìn òkèèrè ṣe fún ìgbéga àṣà àti ìwà ọmọlúàbí, bí àwọn wọ̀nyí ṣe dojú àṣà àti ìwà ọmọlúàbí bolẹ̀ pátápátá. Ní ayé ìgbàanì, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ Yorùbá ló máa ń fẹ́ kí wọ́n pe àwọn ní *"Ọmọlúàbí, tí wọn yóò máa hùwà tí wọn kò fi ní í tẹ àgbà mọ́lẹ̀ tàbí yájú sí ajunilọ'*. Ṣùgbọ́n kò rí bẹ́ẹ̀ mọ́ lóde òní.

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní *'sùúrù ni baba ìwà'*. Bí a bá wo ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọ̀dọ́ òde-òní, sùúrù wọn ti di súúrú. Wọn kò ní ẹ̀mí ìfaradà mọ́, bẹ́ẹ̀ ni wọn kò gbà pé sùúrù lérè mọ́ àti pé Ọlọ́runṣògo ni wọ́n fẹ́ máa lọ. Èyí mú kí ìwà ọmọlúàbí wọ̀ọ̀kùn lọ̀sàn-án gangan.

Gẹ́gẹ́ bí Ìṣọ̀lá ti sọ, lára àwọn ọ̀nà àbáyọ nínú ìṣòro yìí ni pé kí tọmọdé tàgbà jí gìrì sí àṣà wa, kí á máa gbìnyànjú láti polongo rẹ̀ láàrín àwọn èwe àti ọ̀dọ́, kí á máa kọ́ èdè àti àṣà Yorùbá ní ilé ẹ̀kọ́, kí á fọnrere rẹ̀ lórí rédíò àti tẹlifísàn àti àwọn ẹ̀rọ ìgbàlódé mìíràn. Ní pàtàkì jùlọ, kí á máa fi àwọn nǹkan wọ̀nyí kọ́ àwọn ọmọ wa lábẹ́ ọ̀ọ̀dẹ̀ nítorí pé ilé ni a ti ń kó ẹ̀sọ́ ròde.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín yìí ni a ti wo ìwà Ọmọlúàbí gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan pàtàkì nínú ẹ̀ka àṣà Yorùbá, èyí tí kò ṣe é fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn.

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ síwájú, ìwà ọmọlúàbí jẹ́ èyí tí ó ń mú kí ìlọsíwájú, ìgbéga àti àlàáfíà jọba ní àwùjọ Yorùbá ní ayé ìgbàani.

A sọ̀rọ̀ lórí bí àwọn ẹ̀ka àṣà yìí ṣe ń ran àwùjọ lọ́wọ́ tí kò fi sí ìdàrúdàpọ̀ àti èdè-àìyedè láàrín wọn. A wo ìkíni bí ó ṣe ṣe pàtàkì fún àtijoyè ọmọlúàbí, bẹ́ẹ̀ ni a wo ìbọ̀wọ̀-fún-àgbà tí ń mú àwùjọ dàgbà. A tún mẹ́nuba ìhùwàsí àti ìgbé-ayé àwọn ènìyàn ní àwùjọ Yorùbá, èyí tí ó jẹ́ kí àwùjọ tùbà tùṣẹ nígbà náà. Lẹ́yìn náà ni a mẹ́nuba Iṣẹ́-ajé ṣíṣe ní àwùjọ Yorùbá, èyí tí ó jẹ́ ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ fún okun, agbára, ìlera àti àlàáfíà fún àwọn olùgbé àwùjọ.

Ní ìparí, a ṣe atótónu lórí ipò tí àṣà àti ìwà ọmọlúàbí wà lónìí, àti bí àwọn ìyípadà tí kò mú inú dùn ṣe ń dorí àṣà yìí kodò. Lẹ́yìn èyí ni a dábàá àwọn ọ̀nà àbáyọ láti ṣẹ́gun àwọn ìṣòro wọ̀nyí.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Kín ni ọmọlúàbí túmọ̀ sí?
2. Ṣàlàyé ìwà ọmọlúàbí bí ó ṣe yé ọ.
3. Kín ni àwọn àmúyẹ tí wọ́n fi lè ka ènìyàn sí ọmọlúàbí?
4. È̀rè wo ní ń bẹ nínú kí ènìyàn jẹ́ ọmọlúàbí?
5. Ṣe àlàyé lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́ nípa ọmọlúàbí ènìyàn kan tí o mọ̀ àti àwọn ohun àmúyẹ tí o mọ̀ mọ̀ ọ́n.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Ọyádèjì, B. (1986). "Iṣẹ́ Àwọn Yorùbá àti Ìkíni Lẹ́nu Iṣẹ́" in *Fèyíkọ́gbọ́n,* Vol. 17, No. 2, P. 11. Ìbàdàn, Comedy Publications.

Ọyádèjì, B. (1990). "Ìwà Ọmọlúwàbí" in *Fèyíkọ́gbọ́n,* Vol. 21, No. 1, Ìbàdàn, Comedy Publications.

Ariwoọlá, T.A. (1989). *"Ìkíni Ní Ilẹ̀ Yorùbá"* in *Fèyíkọ́gbọ́n,* Vol. 20, No. 2, Ìbàdàn, Comedy Publications.

Fálétí, A. (2009). "Ọmọlúàbí-The Golden Attribute of a Yorùbá-man: Growing or Dying? In Ògúndèjì, A. & Àkàngbé, A. (eds.) in *Ọmọlúàbí Its concept and education in Yorùbáland,* Ìbàdàn, Ìbàdàn Cultural Studies Group.

Ìṣọ̀lá, A. (2009). "Yorùbá Culture in Education" in Ògúndèjì, A. & Àkàngbé, A. (eds.) *Ọmọlúàbí, Its Concept and Education in Yorùbáland,* Ìbàdàn, Ìbàdàn Cultural Studies Group.

Yọ̀lóyè, A. (2009). "The Philosophy of the Nigerian Education System and Relevance to the Concept of the Yorùbá Ọmọlúàbí" in Ògúndèjì, A. & Àkàngbé, A. (eds.) *Ọmọlúàbí, Its Concept and Education in Yorùbáland,* Ìbàdàn, Ìbàdàn Cultural Studies Group.

Ògúndèjì, A. (2009). "Èdè Yorùbá Gẹ́gẹ́ bí Ọkọ̀ tí a fi ń tu Ìwà Ọmọlúàbí Gúnlẹ̀ Sébùté Ayọ̀ Láwùjọ" in Ògúndèjì, A. & Àkàngbé, A. (eds.) *Ọmọlúàbí, Its Concept and Education in Yorùbáland,* Ìbàdàn, Ìbàdàn Cultural Studies Group.

Ládélé, T.A.A. *et al* (eds.) 2006. *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá,* Ìbàdàn Gavima Press Ltd.

## MÓDÙ KEJÌ: ÀWỌN ẸKA ÀṢÀ ŃLÁŃLÁ YORÙBÁ

## ÌPÍN KẸTA: Àṣà Ìbọ̀rìṣà Yorùbá I

***Àkóónú***


1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ìgbàgbọ́ Nínú Àwọn Irúnmọlẹ̀

4.2 Ọbàtálá tàbí Òrìṣàńlá

4.3 Ọ̀rúnmìlà

44 Ògún

4.5 Èṣù Láàlú

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Nínú ìpín yìí ni a ti ṣe àlàyé nípa ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá ní ayé àtijọ́ àti ìdí tí wọ́n fi máa ń bọ àwọn òrìṣà yìí.

Wọ́n gbàgbọ́ pé Olódùmarè ni ó ṣẹ̀dá ohun gbogbo láti ìpilẹ̀ṣẹ̀ àti pé òun ni ó dá àwọn irúnmọlẹ̀ láti máa ṣe àkóso àti ìtọ́jú àwọn ẹ̀dá alàáyè yòókù, ìbáà ṣe ènìyàn tàbí ẹranko igbó.

Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé òrìṣà kọ̀ọ̀kan tí Olódùmarè dá ni ó ní iṣẹ́ tirẹ̀ pàtó tí Ẹlẹ́dàá gbé lé e lọ́wọ́. Lára àwọn òrìṣà wọ̀nyí ni Òrìṣà-ńlá tàbí Ọbàtálá, Ọ̀rúnmìlà tí a tún mọ̀ sí Ifá, Ògún onírè, Ọya, Èṣù láàlú, Ṣàngó, Òrìṣà-oko, Yemọja àti àwọn òrìṣà atẹ̀wọ̀nrọ̀ mìíràn.

Níbí ni a ti wo onírúurú iṣẹ́ tí àwọn òrìṣà wọ̀nyí ń ṣe àti ipò ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ní àwùjọ àwọn irúnmọlẹ̀ wọ̀nyí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a kò le sọ pé ọ̀kan ni àgbà òrìṣà tàbí ọ̀kan ni aṣíwájú, a rí í pé iṣẹ́ takuntakun ni ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ń ṣe. Wàyí ò, àwọn òrìṣà náà pọ̀ débi pé a kò le sọ̀rọ̀ lórí wọn tán nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ṣùgbọ́n a yànnàná iṣẹ́ àti àbùdá díẹ̀ lára wọn níbí.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Èròǹgbà tí a ní fún ìpín yìí ni:

- Kí akẹ́kọ̀ọ́ tàbí òǹkàwé mọ àwọn òrìṣà tí àwọn Yorùbá máa ń bọ ni ìgbà ìwàṣẹ̀ títí di òní olónìí.
- Kí a fi yé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ipò tí àwọn òrìṣà kọ̀ọ̀kan wà ní ìgbà ìwáṣẹ̀.
- Láti tán ìmọ́lẹ̀, kí á sì ṣe àlàyé sí àwọn èèwọ̀ òrìṣà yìí kọ̀ọ̀kan.
- Kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè jíròrò lórí ipò tí àwọn ìbọ wọ̀nyí wà lóde òní, àti ọsẹ́ tí ẹ̀sìn àtọ̀húnrìnwá ṣe ẹ̀sìn ìbọ̀rìṣà Yorùbá.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Òrìṣà mélòó ni Yorùbá máa ń bọ ní ayé àtijọ́, bẹ́ẹ̀ ni kí ó ṣe àlàyé ipò ti márùn-ún wà nínú wọn.
2. Ki díẹ̀ nínú oríkì àwọn òrìṣà mẹ́ta, kí ó sì ṣe àlàyé iṣẹ́ tí Olódùmarè fún wọn ṣe.
3. Ìbáṣepọ̀ wo ló wà láàrín Ògún àti Ọṣọ́ọ̀sì?
4. Kín ni ìdí tí wọ́n fi máa ń da òrìṣà Ọbàtálá pé ní òrìṣà-ńlá?
5. Ìbáṣepọ̀ wo ló wà láàrin Ọ̀rúnmìlà àti ifá?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nínú Àwọn Òrìṣà tàbí Irúnmọlẹ̀

Yorùbá gbàgbọ́ pé ní àtètèkọ́ṣe ni Olódùmarè dá àwọn ọ̀kànlénú (ọ̀kànlénírinwó) àwọn irúnmọlẹ̀ tí ó sì fi ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn sí ìṣàkóso àwọn ẹ̀dá alààyè yòókù. Láìdéènà pẹnu, a lè sọ pé àwọn òrìṣà tàbí irúnnmọlẹ̀ wọ̀nyí jẹ́ àwọn ẹ̀dá tí ènìyàn gbà pé, wọ́n wà, tí àwọn Yorùbá sì gbà pé Olódùmarè fún ní agbára láti máa ṣe àkóso tàbí darí ayé níbi tí ẹ̀dá ènìyàn àti àwọn ẹ̀dá ẹranko ń gbé. Wọ́n gbàgbọ́ pé àwọn òrìṣà wọ̀nyi ni ó lè mú kí ìgbáyégbádùn ẹ̀dá ènìyàn wà ní àlàáfíà, kí nǹkan sì máa lọ déédéé. Yorùbá gbàgbọ́ pé ìwàláàyè kò le gbéwọ̀n láìsí ojúṣe àwọn òrìṣà wọ̀nyí nítorí wọ́n gbà pé àwọn òrìṣà yìí ni máyégún tí wọ́n sì lè mú kí ayé tòrò. Ìdí ni pé àwọn ni aṣojú àti olùrànlọ́wọ́ Olódùmarè lóde ayé.

Gẹ́gẹ́ bí Àlàbí (1981) ṣe sọ, Yorùbá gbàgbọ́ pé àwọn òrìṣà wọ̀nyí ni ẹmẹ̀wà, olùbánidámọ̀ràn àti òjíṣẹ́ fún Ọlọ́run Olódùmarè, bẹ́ẹ̀ ni àkàndá ni wọ́n jẹ́ nínú àwọn iṣẹ́ ọwọ́ Ọba Adẹ́dàá àti pé ó fún wọn ní agbára ọ̀tọ̀.

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ síwájú, àwọn kan gbà pé ọ̀kanlénírinwó (401) ni iye àwọn òrìṣà tàbí Irúnmọlẹ̀, ṣùgbọ́n àwọn mìíràn sọ pé ọ̀kànlérúgba (201) ni. Àwọn mìíràn tilẹ̀ sọ pé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀sán (1,700) ni iye wọn. Nínú Odù Ifá Ọ̀sá Méjì, a sọ fún wa pé ọ̀kànlénírinwó (401) ni wọn nígbà tí odù yìí sọ pé:

Òòlé ló sẹ̀yìn gùnmọ̀lè
Bí ẹni arìnmọ́rìn
Bó bá jáko, a dúró sii
A díá fọ́kànlénú irúmọlẹ̀
Wọ́n ń tọ̀run bọ̀ wáyé…

Nítorí náà, a lè sọ pé ọ̀kanlénírinwó ni àwọn òrìṣà náà jẹ́ gẹ́gẹ́ bí ẹsẹ̀ Ifá òkè yìí ṣe sọ. Yorùbá gbàgbọ́ pé àwọn òrìṣà wọ̀nyí jẹ́ alárenà láàrín Olódùmarè àti àwọn ẹ̀dá ènìyàn, àti pé gbogbo ọ̀nà tí ayé yóò fi rọ àwọn ènìyàn lọ́rùn ni wọ́n máa ń wá.

Láìdéènà pẹnu, àwọn irúnmọlẹ̀ wọ̀nyí ni àwọn Yorùbá máa ń pè ní òrìṣà. Olódùmarè fún àwọn òrìṣà wọ̀nyí ní agbára ọ̀tọ̀. Ọ̀dọ̀ Rẹ̀ ní ìsàlú ọ̀run ni wọ́n ń gbé kí ó tó rán wọn wá sí òde ìsálayé ní àwọ̀ ènìyàn, bẹ́ẹ̀ ni pẹ̀lú àṣẹ Olódùmarè, wọ́n ti ṣe gudugudu méje, yààyàà mẹ́fà pẹ̀lú àṣẹ Ẹlẹ́dàá ayé òun ọ̀run. Nítorí ìdí èyí, a ti rí wọn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí Ọlọ́run ṣà dá. Àwọn òrìṣà wọ̀nyí le bínú bí àwa ọmọ ènìyàn bá ṣẹ̀ wọ́n, bẹ́ẹ̀ ni bí a bá bẹ̀ wọ́n, wọ́n máa ń gbẹ̀bẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìwé ìfáàrà lórí àwọn irúnmọlẹ̀ yìí kò le sọ̀rọ̀ nípa gbogbo wọn, a ó gbìyànjú láti ṣe àlàyé lórí àwọn díẹ̀ nínú wọn.

## 4.2 Ọbàtálá tàbí Òrìṣàálá

Kò sí ènìyàn abẹ̀mí tí ó le sọ̀ àtiwáyé Òrìṣàálá nítorí pé òun ni a kọ́ dá. Gẹ́gẹ́ bí ìtàn àtẹnudétí kan ṣe sọ; Ọbàtálá ni òrìṣà tí Olódùmarè fún ni àṣẹ láti wá ṣètò bí ayé yóò ṣe wà létò lẹ́yìn tí Ọlọ́run ti dá ayé ní ìgbà ìwáṣẹ̀. Ọbàtálá yìí ni a mọ̀ sí òrìṣà aláṣọ funfun nítorí pé aṣọ àlà ni ó máa ń wọ̀ bí ó ti jẹ́ òrìṣà onínú funfun. A máa ń da òrìṣà yìí pè gẹ́gẹ́ bí òrìṣà-ńlá (òrìṣàálá) nítorí ipò rẹ̀ láàrin àwọn irúnmọlẹ̀ yòókù. Èyí ni ọba tí ó tóbi àti pé òun ni Ẹlẹ́dàá kọ́kọ́ dá nígbà ìwáṣẹ̀.

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé Ọbàtálá ni ó mọ ara ènìyàn, tí ó sì fi ojú, imú, àti ẹnu àti àwọn ẹ̀yà ara yòókù sí í gẹ́gẹ́ bí a ti rí lónìí yìí. Wàyí ò, wọ́n gbàgbọ́ pé Ọbàtálá ni ó mọ abuké, arọ, àfín àti àwọn aláàbọ̀ ara yòókù bí wọ́n ṣe rí lónìí.

Ìdí nìyití wọ́n fi máa ń kì í pé

Ẹni ṣojú ṣemú,
Òrìṣà ni máa sìn.
Adáni bó ti rí,
Òrìṣà ni máa sìn…

Àwọn ìtàn ìgbà ìwásẹ̀ kan sọ pé àwọn obìnrin wọ̀nyí ni wọ́n máa ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ọmọ Ọbàtálá nítorí pé àwọn ni Ọbàtálá mọ nígbà tí ó mu ẹmu yó, tí ó sì dá wọn bí ó ti rí. Ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ fi àwọn ẹní òrìṣà yìí ṣe yẹ̀yẹ́ bí wọn kò bá fẹ́ẹ̀ rí ìbínú Ọbàtálá. Ìdí nìyí tí àwọn olùsìn òrìṣà yìí kò fi gbọdọ̀ mu ẹmu ọ̀pẹ.

Yàtọ̀ sí ẹmu ọ̀pẹ tí ó jẹ́ èèwọ̀ fún Ọbàtálá àti àwọn olùsìn rẹ̀, wọ́n kò fẹ́ epo àti osùn ní ojúbọ rẹ̀ bí kò ṣe àlà funfun gbòò. Dípò èyí, àwọn nǹkan tí Ọbàtálá fẹ́ ni iyán àti ọbẹ̀ funfun, gèlè funfun àti ìlẹ̀kẹ̀ funfun tí ìyàwó Ọbàtálá máa ń lò lọ́jọ́ ọdún rẹ̀. Ẹfun ni wọ́n máa ń fi kun ojúbọ rẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni lójoojúmọ́ ni wọ́n gbọ́dọ̀ máa pọn omi sí ojúbọ  yìí, pàápàá ní àárọ̀ kùtùkùtù ni wọn yóò pọn omi yìí.

Ìyàwó kan ṣoṣo tí ń jẹ́ Yemòwó ni Ọbàtálá fẹ́ nítorí pé kò fẹ́ràn ìwọ̀sí àti aáwọ̀. Ìdí nìyí tí a ṣe máa ń gbọ́ nípa tirẹ̀ pé *“a kò lè gbé láàrín ojì ènìynà, kí á máa sì wí”*. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ọbàtálá tàbí Òrìṣàálá ni a mọ orúkọ òrìṣà yìí láàrín àwọn Yorùbá, ṣùgbọ́n ni àwọn agbègbè mìíràn, wọ́n tún máa ń pè é ní àdàpè mìíràn. Bí àpẹẹrẹ, òun ni òrìṣà Ògìyàn ní ìlú Èjìgbò, Òriṣà Gbẹ̀gbẹ̀kun-ẹ̀gbẹ̀ ní Ìlú Ìbàdàn, Òrìṣàròwu ní Orílè-Òwu, Òrìṣàkirè ní Ìlú Ìkirè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## 4.3 Ọ̀rúnmìlà

Ọ̀rúnmìlà jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ọ̀kànlénú irúnmọlẹ̀ tí ó rọ̀ wá sí odè ìsálayé ní ìgbà ìwáṣẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí Ọlájubù (1975:3) ṣe sọ, ó *“jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn òjíṣẹ́ Ọlọ́run, ó sì jẹ́ àyànfẹ́ Rẹ̀”*.

Ọ̀rúnmìlà ni Olódùmarè fún ní ọgbọ́n, ìmọ̀ àti òye láti máa ṣe àkóso ilé ayé bẹ́ẹ̀ ni a gbọ́ pé ó wà pẹ̀lú Ọlọ́run nígbà tí ó ń dá àwọn ẹ̀dá gbogbo, pàápàá ẹ̀dá ènìyàn sórí ilẹ̀ ayé. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń ki Ọ̀rúnmìlà ní:

> Ẹlẹ́rìí-ìpín
> Akéréfinúsọgbọ́n,
> Akọ́nilọ́ràn bí ìyekan ẹni
> Òpìtàn Ilẹ̀ẹfẹ̀.

Bí a bá wo orúkọ yìí, àwọn kan sọ pé ìtumọ̀ rẹ̀ ní *“Ọ̀run ni ó mọ àtilà”* tàbí *‘Ọ̀run ló mọ ẹni tí yóò là’.* Wàyí ò, èyí le jẹ́ oríkì Ọ̀rúnmìlà tàbí orúkọ rẹ̀, ohun tí a mọ̀ dájú ni pé bí nǹkan bá dojúrú tán, bóya láàrín àwọn ènìyàn tàbí láàrín àwọn irúnmọlẹ̀ yòókù, Ifá Ọ̀rúnmìlà ni wọ́n máa ń ké sí láti yanjú ááwọ̀ tàbí ìṣòro bẹ́ẹ̀. Òun ni alárenà

láàrín àwọn ẹ̀dá ènìyàn àti àwọn irúnmọlẹ̀ yìí. Bí ẹ̀dá ènìyàn kan bá tasẹ̀ àgẹ̀rẹ̀ lu àwọn irúnmọlẹ̀ kan láìmọ̀, Ọ̀rúnmìlà ni wọn yóò kó ọ̀ràn náà tọ̀ lọ tí yóò wá ojútùú sí gbódó-n-rósọ bẹ́ẹ̀.

A gbọ́ nínú ìtàn àtẹnudétí kan pé nígbà tí àwọn ọ̀kànlénú irúnmọlẹ̀ wọ̀nyí rọ̀ sí Ifẹ̀-Oòdáyé, Òkè ìgẹ̀tí ni Ọ̀rúnmọlẹ̀ tẹdó sí. Lẹ́yìn ìgbà díẹ̀ ni ó gbéra lọ sí Adó, Ọ̀wọ̀, Benni, Obòkun, Ìṣẹ̀ri àti àwọn Ìlú mìíràn láti lọ máa pẹ̀tù sí ááwọ̀ tàbí láti máa tọ́ àwọn ènìyàn ibẹ́ sọ́nà. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ńń ki Ọ̀rúnmìlà pé;

Erinmi nílé Adó
Erinmi lóde Ọ̀wọ̀
Ṣìkiṣìki lóde Ìṣẹ̀rimogbe

A tún gbọ́ pé Ọ̀rúnmìlà máa ń ṣe awo lọ sí Meréetélú, Mọsẹ̀kálúbà, Ikọ̀ Awúsí, Òdòròmù Àwísẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí a ti tọ́ka sí Ọ̀rúnmìlà gẹ́gẹ́ bí ẹlẹ́rìí-ìpín, ó mọ ìpín tí ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan yàn láti ọ̀run bẹ́ẹ̀ ni ó mọ ọ̀nà àbáyọ sí àwọn ìpín tí kò bá sunwọ̀n. Nítorí náà, àwọn ènìyàn máa ń lọ sí ọ̀dọ̀ ifá láti ṣe ìwádìí nípa ìgbé-ayé wọn àti ọ̀nà tí wọ́n lè gbà borí ìṣòro tí ó bá ṣúyọ.

Kí Ọ̀rúnmìlà tó fi ayé sílẹ̀, ó ti kọ́ àwọn ọmọlẹ́yìn rẹ̀ ni dídá ọwọ́, ó ti kọ́ wọn ní ètìtẹ̀ alẹ̀, ó sì ti kọ́ wọn ni ìkarara ẹbọ. Ó fún wọn ni ikin àti ọ̀pẹ̀lẹ̀ láti máa fi ṣe ìwádìí àwọn ohun tí ó bá rú wọn lójú. Láti ìgbà yìí ni àwọn Yorùbá ti máa ń tọ Ifá lọ fún àyẹ̀wò bóyá wọ́n fẹ́ẹ́ pilẹ̀ ilé ni o, bóyá ọmọ ń ṣe ìgbéyàwó ni, bí wọ́n bá fẹ́ẹ́ múlẹ̀ oko tàbí wọ́n fẹ́ẹ́ bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ tuntun lórí ilẹ̀ tuntun.

Àwọn tí wọ́n bá tí kọ́ṣẹ́ Ifá, tí wọ́n sì ti mọ awo ni a ń pè ní babaláwo, bẹ́ẹ̀ ni àwọn obìnrin kan náà wà tí a ń pè ní ìyánífá. Àwọn ìyánífá yìí máa ń dáfá ṣùgbọ́n wọn kì í lo ikin tàbí ọ̀pọ̀lẹ̀, èyí tí a mọ̀ mọ àwọn babaláwo tó gbọ́fá yanrányanrán.

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ènìyàn bíi tiwa ni Ọ̀rúnmìlà nígbà kan, ó sì jẹ́ gbáyé gbọ́run nítorí a máa lọ ran Olódùmarè lọ́wọ́ lóde ọ̀run lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan ṣùgbọ́n ó gbé òde ayé fún ìgbà pípẹ́ kí ó tó padà lọ sí ìsàlú ọ̀run.

Gẹ́gẹ́ bí ẹ̀sìn, àwọn tó ní ìgbàgbọ́ nínú agbára àti ipò tí Ọ̀rúnmìlà wà nígbà tó wà lóde ayé ni wọ́n gbà á gẹ́gẹ́ bí òrìṣà lẹ́yìn tí ó ti fi ayé sílẹ̀ tán. Èyi kò ṣàjèjì sí àṣà tàbí ìpèdè Yorùbá kan tí ó sọ pé bí a kú là á dère, ènìyàn kò ṣunwọ̀n láàyè. Ìgbàgbọ́

Yorùbá náà ló rọ̀ mọ́ àwọn òrìṣà yòókù gẹ́gẹ́ bí Ṣàngó, Ògún, Ọya, Ọ̀ṣun àti àwọn ènìyàn àkàndá mìíràn tí ó jẹ́ pé lẹ́yìn ikú wọn ni wọ́n sọ wọ́n di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ.

Ìgbàgbọ́ àwọn olùsin Ọ̀rúnmìlà ni pé kò sí ohun tí kò le ṣe fún wọn-ẹ̀mí gígùn ire owó, ire ọmọ àlàáfíà, ìṣẹ́gun lórí ọ̀tá, àtàjèrè ọjà, ààbò lọ́wọ́ ọ̀tá àti ewu gbogbo. Nítorí náà, láti rí ojúrere òrìṣà yìí, wọ́n máa ń ya àwọn ọjọ́ kan sọ́tọ̀ láti bọ ọ́, èyí tí wọ́n máa ń pè ní ọdún Ifá. Ọdún Ifá yìí lè wáyé ní ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀, oṣoosù tàbí ní ọdọọdún.

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ síwájú, àwọn tí ó jẹ́ àwòrò níbi ẹ̀sìn Ifá ni a ń pè ní babaláwo. Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, a máa ń pè wọ́n ní *"bàbá aláṣìírí"* nítorí iṣẹ́ awo tí wọ́n ń ṣe. Nítorí náà, Ifá dídá dá lórí bíbèèrè lọ́wọ́ Ifá àwọn ohun tí oníbàárà yóò ṣe láti borí ìṣòro tàbí àníyàn tí ó ní, èyí tí ó gbé e wá sí ọ̀dọ̀ babaláwo. Díẹ̀ lára irúfẹ́ ìṣòro bẹ́ẹ̀ ni àìrọ́mọbí, àìláya, àìlọ́kọ àti ìṣẹ́gun lórí àwọn ajogun gbogbo bí ikú, àrùn, òfò, ẹ̀gbà àti èṣe.

## 4.4 Ògún

Òrìṣà Ògún jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn ọ̀kànlénú irúnmọlẹ̀ atẹ̀wọ̀nrọ̀ èyí tí ọ̀kan nínú àwọn ìtàn ìgbà íṣẹ̀ sọ pé òun ni ó lànà fún àwọn irúnmọlẹ̀ náà láti ìsàlú ọ̀run wá sí Ifẹ̀-Oòdáyé láìsí wàhálà kankan. Ògún yìí ni òrìṣà gbogbo àwọn tí ń lo irin láti fi ṣe iṣẹ́ ajé wọn tàbí ohun mìíràn tí ó jẹ irin lílò. Bí àpẹẹrẹ, àwọn àgbẹ̀ tí ń lo àdá, ọkọ́, ọ̀bẹ, ààké àti àwọn ohun èlò irin mìíràn. Àwọn mìíràn ní àwọn onímọ́tò, àwọn gbẹ́nàgbẹ́nà, àwọn ọdẹ, àwọn apẹja àti àwọn oníṣẹ́ ọwọ́ mìíràn lóríṣiríṣi. Ní pàtó, ó fẹ́rẹ̀ẹ́ máa sí ènìyàn tí ọ̀nà rẹ̀ kò jẹ mọ́ irin lílò, bẹ́ẹ̀ ni òrìṣà Ògún ni ó ni irin.

Yorùbá bẹ̀rù òrìṣà Ògún púpọ̀ nítorí pé wọ́n gbàgbọ́ pé òrìṣà tí kò fẹ́ irọ́ pípa ni. Wọ́n gbàgbọ́ pé Ògún lè pa ẹnikẹ́ni tí ó bá fi Ògún búra èké. Ìtàn ìgbà ìwásẹ̀ kan tilẹ̀ sọ pé nígbà tí Ògún rọ̀ sí Ifẹ̀-Oòdáyé pẹ̀lú àwọn òrìṣà yòókù, ó gba òde Ìrè lọ. Níbẹ̀ ni ó ti bẹ̀rẹ̀ sí í dẹ igbó láti pa ẹran àti pé nígbà tí ó padà sínú ìlú, ó bẹ̀rẹ̀ sí í sọ ìrírí rẹ̀ nínú igbó, èyi tí ó ń sọ pẹ̀lú ohùn ìjálá àti ìrèmọ̀jé.

Káàkiri ilẹ̀ Yorùbá ni wọ́n ti máa ń ṣe ọdún Ògún bẹ́ẹ̀ ni ọdún yìí ni ó gbajúgbajà jù lọ láàrín àwọn Yorùbá ní ayé àtijọ́. Ìdí ni pé kò sí ibi ti wọn kì í tí bọ Ògún lọ́dọọdún ní àwùjọ Yorùbá, bẹ́ẹ̀ ní àkókò tí iṣu tuntun bá jáde, nínú oṣù keje sí ẹ̀kẹjọ ni wọ́n sábà máa ń ṣe ọdún Ògún. Àwọn ohun tí wọ́n fi máa ń bọ ògún ni ajá,

iyán, ẹ̀wà ẹ̀yan. Epo, adìẹ, obì àti ẹmu. Ọjọ́ méje ni ọdún Ògún ń gbà kí ó tó parí, bẹ́ẹ̀ ni tọmọdé tàgbà ló máa ń gbadùn àsìkò ayẹyẹ ọdún náà.

## 4.5 Èṣù Láàlú

Gẹ́gẹ́ bí àwọn yòókù, Èṣù náà jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọ̀kànlénú irúnmọlẹ̀ tí ó rọ̀ láti ìsàlú ọ̀run wá sí òde ìsálayé ní ìgbà ìwásẹ̀. Káàkiri ilẹ̀ Yorùbá ni wọ́n ti mọ Èṣù láàlú gẹ́gẹ́ bí òrìṣà àkúnlẹ̀bọ. Èṣù jẹ́ ọ̀kan lára àwọn oríṣà tí ó ní ìgboyà àti ọgbọ́n àrékérekè, ó gbójú, ó gbónu, ó sì ní akíkanjú. Ìdí nìyí tí ó fi ní ipò pàtàkì láàrin àwọn òrìṣà ẹgbẹ́ rẹ̀ yòókù, bẹ́ẹ̀ ni ipò rẹ̀ kò kẹ́rẹ̀ láàrín àwùjọ ènìyàn àgbáyé, pàápàá láàrín àwọn Yorùbá.

A fi yé wa pé Èṣù àti Ọ̀rúnmìlà súnmọ́ ara wọn tó bẹ́ẹ̀ tí ó jẹ́ pé kòríkòsùn ni wọ́n jẹ́. Èṣù yìí ni ó máa ń ṣe alàgàta láàrin àwọn irúnmọlẹ̀, ẹ̀dá ènìyàn àti Ifá, tí ó sì máa ń pẹ̀tù sí aáwọ̀ nígbàkigbà tí èdè-àìyedè bá wáyé láàrin wọn. Bí òrìṣà kan bá ní aáwọ̀ pẹ̀lú òrìṣà mìíràn tàbí tí ènìyàn bá ṣẹ̀ sí òfin òrìṣà kan, Èṣù ni yóò ṣe ìwádìí irú èdè-àìyedè bẹ́ẹ̀ tí yóò sì jẹ́ kí Ifá mọ̀ sí èyí. Lẹ́yìn èyí ni Ọ̀rúnmìlà yóò ṣe ìwádìí lọ́wọ́ Ifá láti mọ ọ̀nà àbáyọ, tí yóò sì yanjú rẹ̀ ní ìtùnbí-ìnùbí.

Èṣù ló kọ́kọ́ máa ń jẹ kí òrìṣà yòókù tó jẹ nítorí òun ni yóò mọ ohun ètùtù, tí yóò sì gbà ìpín tirẹ̀ kí ó tó dé ọ̀dọ̀ Ọ̀rúnmìlà tàbí kí òrìṣà tí ó kàn tó gba tirẹ̀. Èṣù yìí pàápàá máa ń gba ẹbọ lọ́wọ́ àwọn olùsin rẹ̀ nígbàkígbà tí ó bá fẹ́, bẹ́ẹ̀ ni àwọn olùsìn yìí kì í fi ọ̀rọ̀ rẹ̀ jáfara.

Àwọn ẹlòmíràn máa ń wòye pé òrìṣà tí ó burú jáì ni Èṣù jẹ́ ṣùgbọ́n àwọn Yorùbá gbà pé olùgbèjà àwọn aláìlágbára ni òrìṣà yìí, tí ó sì máa ń gbà wọn lọ́wọ́ àwọn ajunilọ tí í fọwọ́ ọlá gbáni lójú. Lára àwọn ohun tí wọ́n fi máa ń bọ Èṣù ni òbúkọ, epo, ajá, àkùkọ adìẹ, ìgbín, ẹ̀kọ àti obì, bẹ́ẹ̀ ni àwọn mìíràn, pàápàá àwọn àgbẹ̀ sábà máa ń ta Èṣù lọ́rẹ iṣu, àgbàdo, ẹyin, ìgbá, ọ̀gẹ̀dẹ̀ àti àwọn èso mìíràn bí wọ́n bá ti ń ti oko ẹgàn bọ̀. Ṣùgbọ́n ṣá o, òrìṣà Èṣù kórìíra àdí.

A máa ń rí ojúbọ Èṣù káàkiri agboolé àti ìlú ńlá mìíràn. Àwọn olùsìn rẹ̀ máa ń fi orúkọ òrìṣà sọ ìlú wọn nígbà mìíràn. Bí àpẹẹrẹ, a rí Abúlé Eléṣù tí ó wà nítòsí Oyèdèjì ní Ìjọba Ìbílẹ̀ Lágelú ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ bẹ́ẹ̀ ni a máa ń rí ojúbọ Èṣù ní ibikan tí a ń pè ní *'Èṣù Àwẹ̀lé'*, nítòsí àdúgbò Ọjà-Iba ní Ìlú Ìbàdàn.

Ẹ̀ṣù máa ń pèsè ọmọ fún àwọn olùsìn rẹ̀, pàápàá àwọn olùsìn rẹ̀ tí kò bá tètè rí ọmọ bí. Irúfẹ́ àwọn ọmọ bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń sọ orúkọ wọn ní Ẹ̀ṣùbíyìí, Ẹ̀ṣùgbèmí, Ẹ̀ṣùbùnmi àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ní pàtó, òrìṣà Ẹ̀ṣù kò burú tó bí àwọn mìíràn ṣe rò ó sí ṣùgbọ́n ó jẹ́ òrìṣà tí ó máa ń pẹ̀tù síjà láàrin àwọn òrìṣà mìíràn àti láàrin àwọn ènìyàn àti àwọn òrìṣà wọ̀nyí, gẹ́gẹ́ bí ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín yìí ni a ti ṣàlàyé nípa àwọn ẹ̀ka àṣà Yorùbá ńláńlá níwọ̀n bí a ṣe mọ̀ pé àṣà gbòòrò púpọ̀. A kò lè kó gbogbo ẹ̀ka àṣà Yorùbá sí ojúkan, kí a sì máa ṣe àlàyé ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́. Ìdí nìyí tí a fi pín wọn sí ẹ̀ka àṣà ńláńlá àti àwọn ẹ̀ka kéékèèkéé. Nínú àwọn ti a tọ́ka sí bí ẹ̀ka ńláńlá wọ̀nyí, a kò le sọ̀rọ̀ lórí ẹ̀ka yìí tán bí kò ṣe pé kí á mú díẹ̀ pàtàkì nínú wọn.

Níbí yìí ni a ti wo àwọn ẹ̀ka àṣà ìbọ̀rìṣà tí a sì wo àwọn díẹ̀ nínú àwọn òrìṣà atẹ̀wọ̀nrọ̀ kan àti bí Yorùbá ṣe ń bọ wọ́n. Kì í ṣe gbogbo àwọn ẹ̀ka àṣà ìbọ̀rìṣà yìí ni a lè mẹ́nubà bí kò ṣe pé kí á wo díẹ̀ pàtàkì nínú wọn. Ìdí nìyí tí a fi wo àwọn òrìṣà bíi Ọbàtálá, Ọ̀rúnmìlà, Ògún, àti Ẹ̀ṣù Láàlú ní abala yìí. A tọ́ka sí ipò tí àwọn òrìṣà yìí kọ̀ọ̀kan wà àti ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa wọn.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Dárúkọ òrìṣà atẹ̀wọ̀nrọ̀ mẹ́ta tí ó mọ̀ àti ipò wọn láàrín àwọn ìbọ.
2. “Òrìṣà burúkú ni Ẹ̀ṣù Láàlú”! Dá sí ọ̀rọ̀ yìí.
3. Ìbáṣepọ̀ wo ló wà láàrín Ọ̀rúnmìlà àti Ẹ̀ṣù?
4. Ṣé àlàyé nípa ọdún Ògún ní ìlú rẹ.
5. Àwọn oyè pàtàkì wo ló wà nínú ẹ̀sìn Ọ̀rúnmìlà tàbí Ifá?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Àlàbí, O. (1981). "Ipa Tí Àwọn Òrìṣà Kó Láàrín Àwọn Yorùbá àti Olódùmarè" in *Yorùbá Gbòde*, Ìbàdàn, Macmillan Nigeria Publishers Ltd.

Dáramọ́lá, O. & Jẹ́jẹ́, A. (2014). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn Oníbọn-Òjé Press.

Ládélé, A.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*, Ìbàdàn, Gavima Press Ltd.

Ọlágbèmí, B.T. (1978). "Ǹjẹ́ Òrìṣà Ni Orí" in *Yorùbá Gbòde, Vol. 2, No. 3*. Ìbàdàn, Yọ́kẹ́lẹ́ Pẹkùn Press.

Ologundudu, D. (2008). *The Gaddle of Yorùbá Culture*, U.S., Center for Spoken Words/Institute of Yorùbá Culture.

Owólabí, K. *et al* (2015). *Jẹ́ ká Bára wa sọ̀rọ̀ ní Yorùbá, A Multi-Dimensional Approach to the Teaching and Learning of Yorùbá As a Foreign Language*, Bloomington, Indiana, NALRC Press.

Ọyádèjyí, B. (1986). "Iṣẹ́ Àwọn Yorùbá àti Ìkíni Lẹ́nu Iṣẹ́", in *Fèyíkọ́gbọ́n*, vol. 17, No 2 Comedy Publications Company.

Sàlámì, A. (2008). *Yorùbá Theology and Tradition*, Lagos, NIDD Publishing Company Ltd.

## MÓDÙ KEJÌ

## ÌPÍN KẸRIN: ÀṢÀ ÌBỌRÌṢÀ YORÙBÁ II

***Àkóónú***

1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ṣàngó

4.2 Ẹ̀là

4.3 Òrìṣà-Oko

44 Yemọja

4.5 Ṣànpọ̀nná

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Èyí ni ìpín kẹrin nínú módù kejì, èyí tí ó ṣe àlàyé ní ìtẹ̀síwájú àṣà òrìṣà bíbọ tí a mẹ́nubà ní ìpín kejì. Nínú ìpín yìí ni a ti wo àwọn òrìṣà márùn-ún mìíràn tí wọ́n tún ń kó ipa pàtàkì nínú àwọn ìbọ láàrín àwọn Yorùbá. Lára wọn ni Ṣàngó, Ọya, Òrìṣà-Oko, Yemọja àti Ṣànpọ̀nná. Gẹ́gẹ́ bí àwọn òrìṣà tí a ti ṣe àlàyé wọn ní ìpín kẹta módù yìí, àwọn òrìṣà wọ̀nyí jẹ́ òrìṣà tí kò ṣe é fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nínú ìṣàkóso ayé, bẹ́ẹ̀ ni ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ni ó ní ipa tí ó ń kó àti iṣẹ́ tí Olódùmarè fi ran wọn nínú ìtẹ̀síwájú ayé ẹ̀dá ènìyàn. Bí a bá wo àwọn òrìṣà wọ̀nyí, ó ní ipò tí wọ́n wà àti ìbáṣepọ̀ wọn pẹ̀lú àwọn ìrúnmọlẹ̀ yòókù.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Ní ṣókí, èròǹgbà wa ni pé kí akẹ́kọ̀ọ́:

- Le ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìmọ̀ lórí àwọn òrìṣà wọ̀nyí.
- Máṣe lérò pé àwọn Yorùbá kò bọ àwọn òrìṣà wọ̀nyí mọ́ lóde òní.
- Le ní òye lórí ìbáṣepọ̀ àwọn ènìyàn yìí àti àwọn irúnmọlẹ̀ yòókù.
- Le ṣe àlàyé ìyípadà tí ó ń dé bá àṣà bíbọ àwọn òrìṣà wọ̀nyí ní òde-òní.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Kín ni ohun tí o mọ̀ nípa bíbọ òrìṣà Ṣàngó láyé àtijọ́ àti agbára rẹ̀ lóde òní?
2. Ṣe àlàyé ìbátan tí ó wà láàrín òrìṣà Ṣàngó àti Ọya.
3. Irú òrìṣà wo ni Yemọja í ṣe àti pé kín ni wọ́n fi máa ń bọ ọ́?
4. Kín ni ìdí tí wọn fi máa ń pe Òrìṣà-oko ní orúkọ yìí?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ṣàngó

Ṣàngó jẹ́ òrìṣà kan tí ìrísí àti ìwà rẹ̀ máa ń ba àwọn ènìyàn lẹ́rù. Ìtàn àtẹnudétí kan sọ fún wa pé Ọba ni Ṣàngó ní Ọ̀yọ́-Ilé ní ìgbà ayé rẹ̀ àti pé òun ni Aláàfin kẹrin ní ìlú náà kí ó tó di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ. Gẹ́gẹ́ bí Ọba aláde, Ṣàngó ní ìgboyà, ó sì ní òògùn púpọ̀. A gbọ́ pé bí ó bá ń sọ̀rọ̀, ńṣe ni iná máa ń jáde lẹ́nu rẹ̀. Kò sí ìjòyè tàbí ará ìlú tí ó le kọ ọkà Ṣàngó kéré kí ẹbọra má bọ́ onítọ̀hún láṣọ.

Kí Ṣàngó tó kúrò láyé ni ó ti di ẹ̀rùjẹ̀jẹ̀ sí àwùjọ lọ́rùn. Ìtàn sọ fún wa pé èdè-àìyedè kan bẹ́ sílẹ̀ láàárín Gbọ̀nńkáà àti Tìmì Àgbàlé tí wọ́n jẹ́ níejì nínú àwọn olóyè ṣàngó nígbà náà. A gbọ́ pé ṣàngó rí i pé àwọn olóyè méjì wọ̀nyí ń fún òun ní ìyọnu, ó sì kọjú ara sí arọ wọn láti jọ ṣe ìfagagbága ìjà. A gbọ́ pé nígbà tí àwọn olóyè méjeèjè yìí kojú ara wọn, Gbọ̀nńkáà borí Tìmì Àgbàlé, èyí tí kò dùn mọ́ Ṣàngó nínú. Ṣàngó tún rán Gbọ̀nńkáà lọ bá Tìmì ní Ẹdẹ tí ó wà láti lọ gbé orí rẹ̀ wá lérò pé Gbọ̀nńkáà kò ní í bọ̀ ṣùgbọ́n Gboǹńkáà tún borí Tìmì Àgbàlé.

Nígbà tí ẹnu Ṣàngó kò ká àwọn ènìyàn àti àwọn ìjòyè rẹ̀ wọ̀nyí mọ́, ó bínú fi orí àpèrè sílẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni Ọya tí í ṣe ìyàwó rẹ̀ tẹ̀ lé e. nígbà tí ó dé ìdí igi àáyàn kan, Ṣàngó pokùnso níbẹ̀. Ṣùgbọ́n sá o, àwọn ẹmẹ̀wà rẹ̀ kò fẹ́ kí àwọn ará ìlú mọ àṣírí yìí, wọn sọ fún ìlú pé Ṣàngó bínú wọlẹ̀ ni, àti pé ibi tí ó ti wọlẹ̀ náà ni **'kòso'.** Láti ìgbà yìí ni ó ti di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ, tí tọmọdé tàgbà ń bẹ̀rù rẹ̀. Lẹ́yìn ìpapòdà rẹ̀, àwọn ènìyàn kò jẹ́ gúnyán Ṣàngó, kí wọ́n má fi ewé bò ó, nítorí ó le rán àárá sí àarin wọn.

Láyé òde-òní, àwọn Yorùbá bẹ̀rù Ṣàngó àti àwọn olùsìn rẹ̀ kí ó máa baà rán iná ọmọ ọ̀rara sí wọn. Títí di òní olónìí ni wọ́n máa ń bọ òrìṣà Ṣàngó bẹ́ẹ̀ ni Aláàfin máa ń kópa pàtàkì nígbà ọdún Ṣàngó ọlọ́dọọdún.

Lára àwọn olóyè tàbí àwòrò Ṣàngó ni Adóṣù Ṣàngó àti Mọgbà tàbí Ìyá Mọgbà. Àwọn Adóṣù Ṣàngó wọ̀nyí máa ń di irun orí wọn gẹ́gẹ́ bíi ti obìnrin. Ní àkókò ọdún Ṣàngó, òjò gbọ́dọ̀ rọ̀, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó máa ń yanì lẹ́nu bí èyí ṣe máa ń rí bẹ́ẹ̀, ṣùgbọ́n àwọn olùsìn ṣàngó gbà pé Òrìṣà yìí ni ó máa ń mú òjò wá. A kò ní í ṣàìmẹ́nu bà á pé ní àkókò tí òjò bá ń rọ̀ yìí, àwọn Oníṣàngó yóò máa jó káàkiri nínú òjò, wọn yóò máa súre fún gbogbo ènìyàn, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò máa gba ẹ̀bùn lóríṣiríṣi. Nígbà tí òjò bá ń rọ̀,

àárá yóò máa ṣán kíkankíkan, bẹ́ẹ̀ ni ẹdun àárá yóò máa bọ́ láti òkè wá. Ìdí nìyí tí wọ́n ṣe máa ń pe Òrìṣà Ṣàngó yìí ní *'Jàkúta'*, èyí tí ó túmọ̀ sí ẹni tí ń jà pẹ̀lú òkúta. A ó ṣe àkíyèsí pé àwọn Oníṣàngó ni ó máa ń sin òkú ẹni tí àárá bá pa.

Àwọn oúnjẹ tí a fi ń bọ Ṣàngó ni orógbó, adìẹ àti àgùtàn, bẹ́ẹ̀ ni ejò ọká kì í jìnnà sí ibi tí wọ́n bá ti ń bọ Ṣàngó nítorí pé ó fẹ́ràn láti máa jẹ ejò yìí.

Láàrin àwọn Ọ̀yọ́ ni àṣà bíbọ Ṣàngó ti gbilẹ̀ jù, ṣùgbọ́n wọ́n tún máa ń bọ Ṣàngó ní Ìlú Ìbàdàn, Ìṣẹ́yìn, Ìwó àti àwọn Ìlú mìíràn ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun. Àwọn olùsìn Ṣàngó máa ń tọrọ ọmọ lọ́wọ́ Òrìṣà yìí; ìdí sì nìyí tí wọ́n ṣe máa ń sọ ọmọ wọn ní orúkọ bíi Ṣàngógbèmí, Ṣàngótọ́lá, Ṣàngógbàmí àti Ṣàngówánwá.

Àṣà Ṣàngó bíbọ yìí kò tí ì kásẹ̀ nílẹ̀ títí di òní olónìí bẹ́ẹ̀ ni àṣà ṣíṣe orò tàbí ètùtù fún àwọn tí àárá bá pa sì ń tẹ̀síwájú.

### 4.2 Òrìṣà Ẹ̀là

Nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa Òrìṣà Ẹ̀là, ìtàn àtẹnudénu kan sọ fún wa pé ìbáṣepọ̀ wà láàrin Ọ̀rúnmìlà àti Ẹ̀là, wọ́n sì máa ń tọ́ka sí Òrìṣà Ẹ̀là yìí gẹ́gẹ́ bí ọmọ bíbí inú Àgbọnmìrègún. Nígbà mìíràn, wọ́n máa ń tọ́ka sí Ẹ̀là gẹ́gẹ́ bí ìránṣẹ́ Ọ̀rúnmìlà tàbí ọ̀rẹ́ Ọ̀rúnmìlà. Ohun yòówù kí ìbátan tàbí ìbáṣepọ̀ yìí jẹ́, a ṣe àkíyèsí pé ìbámu rẹ́gírẹ́gí máa ń sábà wà nínú ìṣe àti ìsìn àwọn òrìṣà méjèèjì yìí. Bí àpẹẹrẹ, bíbọ Ọ̀rúnmìlà jẹ mọ́ lílo èkùrọ́ bẹ́ẹ̀ ni bíbọ Ẹ̀là ní nǹkan án ṣe pẹ̀lú ọ̀pẹ nítorí pé ìdí ọ̀pẹ ni wọ́n ti máa ń bọ Ẹ̀là. Èyí nìkan kọ́, ní kété tí wọ́n bá ti ṣe ọdún Ẹ̀là tán ni ti Ọ̀rúnmìlà yóò bẹ̀rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni bí wọ́n bá ń ṣe Ọdún Ọ̀rúnmìlà lọ́wọ́, wọ́n ní láti máa rántí Ẹ̀là pẹ̀lú. Ìyàtọ̀ tí a lè tọ́ka sí ni àwọn ohun èló fún àwọn òrìṣà méjèèjì yìí. Bí àpẹẹrẹ, wọ́n máa ń lo èkùrọ̀ fún Ifá, tí wọ́n ń lo eyín erin fún Ẹ̀là.

Yorùbá gbàgbọ́ pé Ẹ̀là wá sí ayé láti wá ṣe àtúnṣe àwọn ohun tí ó mẹ́hẹ ni. Ó ṣe pàtàkì láti ṣe àkíyèsí pé a máa ń pe Ẹ̀là ní *'Ọmọ Ọṣìn'* tí í ṣe Ọba tàbí Aláṣẹ tí ó jú àwọn aláṣẹ yòókù lọ. Yorùbá gbàgbọ́ pé kò sí aláṣẹ mìíràn tí ó ga ju Olódùmarè lọ. Nítorí náà, wọ́n gbà pé ọmọ Olódùmarè ni Ẹ̀là í ṣe. Ìdí nìyí tí àwọn mìíràn ṣe máa ń fi Ẹ̀là yìí wé Jésù inú Bíbélì, ẹni tí ó wá láti ra ayé padà kúrò nínú ìparun.

Ẹ̀là ni wọ́n mọ̀ sí onísùúrù àti onínúure, tí ó máa ń mú ìlú tòrò, tí ó sì máa ń pẹ̀tù sí agbọn ibi tí rògbòdìyàn tàbí ìdàrúdàpọ̀ bá ti fẹ́ẹ̀ wáyé. Yorùbá gbàgbọ́ pé Ẹ̀là jẹ́

òrìṣà tí ó máa ń tún orí ẹni tí kò sunwọ̀n ṣe, bẹ́ẹ̀ ni ó wá sáyé láti ṣe ẹ̀dá ènìyàN lóore láìgba ẹ̀bun rárá. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé iṣẹ́ rere ni Ẹ̀là wá ṣe fún àwọn ènìyàn nínú ayé, ìtàn àtẹnudétí kan sọ fún wa pé ńṣe ni ọmọ aráyé fi ibi ṣú olóore, bẹ́ẹ̀ ni Ẹ̀là pàṣẹ pé kí okùn kan sọ̀kalẹ̀ wá láti ìsàlú ọ̀run èyí tí ó gùn padà lọ sí ọ̀dọ̀ Olódùmarè.

## 4.3 Òrìṣà-Oko

Ọ̀kan nínú àwọn ọ̀kànlénú irúnmọlẹ̀ ni Òrìṣà-Oko í ṣe. Ènìyàn ni òrìṣà yìí kí ó tó fi ayé sílẹ̀, ṣùgbọ́n òun náà di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ gẹ́gẹ́ bí àwọn irúnmọlẹ̀ yòókù. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí agbára àti ìwà rere tí ó ní nígbà tí ó wà láyé. Ṣé Yorùbá bọ̀, wọ́n ní *"Ìgbà a kú làá dère, ènìyàn kò sunwọ̀n láàyè"*. Èyí túmọ̀ sí pé nígbà tí ènìyàn bá fi ayé sílẹ̀ ni àwọn ọmọ aráyé tó máa ń mọ rírì iṣẹ́ dáadáa tí onítọ̀hún ṣe kí ó tó pa ipò dà.

Ìtàn kan fi yé wa pé ogbójú ọdẹ kọ́kọ́ ni Òrìṣà-oko nígbà ayé rẹ̀. Ó sì jẹ́ àgbẹ̀ paraku, ṣùgbọ́n nígbà tí ó dògbó, ó fi iṣẹ́ ọdẹ sílẹ̀, ó sì bẹ̀rẹ̀ sí í ṣe iṣẹ́ àfọ̀ṣẹ àti iṣẹ́ awo. Nínú iṣẹ́ àfọ̀ṣẹ àti iṣẹ́ awo yìí, Ògúnjẹ́miní tí ó wá padà di *'Òrìṣà-Oko'* yìí bẹ̀rẹ̀ sí í tún orí ẹni tí kò sunwọ̀n ṣe. Ó ń gbà wọ́n lọ́wọ́ oṣó àti àjẹ́. Ó ń gba agbára lọ́wọ́ àwọn olùṣebi, ó sì ń mú kí ayé dẹrùn fún àwọn aláìlágbára. Ní pàtó, ọkùnrin yìí lo agbára rẹ̀ fún ìlọsíwájú àti àlàáfíà Ìlú rẹ̀ tí a mọ̀ sí Ìpóló, èyí tí ó wà ní Òkè-Ògùn ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́.

Gẹ́gẹ́ bí ìtàn mìíràn ṣe sọ, lẹ́yìn tí Ògúnjẹ́miní pa ipò dà tán, wọ́n mọ rírì iṣẹ́ tí ó ti ṣe nígbà ayé rẹ̀, wọ́n bèèrè lọ́wọ́ Ifá àwọn ọ̀nà tí wọn yóò gbà láti máa bọ ọ́ àti pé níbo ni wọn yóò ti máa bọ ọ́? Ifá sọ fún wọn pé inú oko níbi tí ọkùnrin yìí ti paradà di igi ńlá kan ni wọn yóò ti máa bọ ọ́ tí yóò sì máa jẹ́ wọn. Ìdí nìyí tí wọ́n fi ń pè é ní Òrìṣà-Oko títí di òní olónìí.

Ọdọọdún ni wọ́n máa ń bọ Òrìṣà-oko yìí, bẹ́ẹ̀ ni ní àkókò iṣu tuntun ni wọ́n máa ń ṣe ìrántí rẹ̀. Gbogbo àwọn olùsìn Òrìṣà-oko ni yóò fi ẹfun sa ojú ní àsìkò ọdún Òrìṣà-oko. Iyán, ọbẹ̀ ẹ̀gúsí àti ìká ẹja ní wọ́n fi máa ń bọ òrìṣà yìí bẹ́ẹ̀ ni lẹ́yìn ètùtù tí oko àti ti ilé, wọn yóò jó káàkiri Ìlú pẹ̀lú Ìlù, ìfọn àti orin láti ṣe ìrántí òrìṣà yìí. Àwọn olùsìn òrìṣà yìí máa ń tọrọ nǹkan lọ́wọ́ rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, wọ́n lè tọrọ ọmọ àti àwọn ohun mìíràn tí wọ́n bá ṣe aláìní. Ìdí nìyí tí wọ́n ṣe máa sọ orúkọ ọmọ wọn ní Òrìṣàbùnmi, Abóríṣàdé, Òòṣàgbèmí, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Èèwọ̀ òrìṣà yìí ni pé àwọn olùsìn rẹ̀ kò gbọdọ̀ jẹ ẹran ehoro.

## 4.4 Yemọja

Yemọja jẹ́ òrìṣà odò tàbí òrìṣà inú omi. Àwọn kan sọ pé ohun tí ó túmọ̀ sí ni *'Yèyé-Ọmọ-Ẹja'* tàbí *'Ìyá gbogbo àwọn Ẹja'*. Láìdéènà pẹnu, Yemọja jẹ́ òrìṣà odò. Láàrín àwọn Yorùbá, wọ́n gbà Yemọja gẹ́gẹ́ bí olùdáàbò bo àwọn ọmọ wẹ̀ẹrẹ. Òun ni òrìṣà omi òkun àti ti ọ̀sà àti àwọn odò mìíràn tí ń ṣàn wọnú òkun tàbí ọ̀sà lọ.

Yemọja ni a ń pè láti gba ètùtù ẹni tí odò bá gbé lọ tàbí tí ó kú sínú omi. Ìdí ni pé òun ni òrìṣà odò. Àwọn mìíràn máa ń jiyàn pé Yemọja àti Olókun yàtọ̀ sí ara wọn ṣùgbọ́n èyí kò rí bẹ́ẹ̀ rárá. Ohun tí a mọ̀ dájú ni pé Yemọja ni òrìṣà Odò Ògùn, tí orísun rẹ̀ wà ní Ṣẹ̀pẹ̀tẹrí ni Òkè-Ògùn ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, èyí tí ó ṣàn kọjá lẹ́bàá Ìlú Ìsẹ́yìn, kí ó tó gba ààrín Ìlú Abẹ́òkúta tí ó sì da omi rẹ̀ sínú ọ̀sà, bẹ́ẹ̀ ní òun ni ó di ọ̀sà. Ìtàn mìíràn tún sọ síwájú sí ì pé odò yìí náà ló di òkun. Nítorí náà, a le sọ pé Yemọja náà ni olókun tí a máa ń gbọ́.

Àwọn olùsìn Yemọja máa ń bọ ọ́. Bí ẹnikẹ́ni bá rì sínú odò, Yemọja ni wọn yóò pè láti gbà wọ́n bẹ́ẹ̀ ni bí ẹni náà bá yè, wọn yóò sọpẹ́ lọ́dọ̀ Yemọja.

Etí odò ni ojúbọ Yemọja máa ń wà, bẹ́ẹ̀ ni ẹnikẹ́ni tí ó bá fẹ́ sọpẹ́ ní ọjọ́ ọdún yóò ṣe ègbo èyí tí ó jẹ́ oúnjẹ Yemọja. Àwọn àwòrò Yemọja máa ń sábà wọ ìlẹ̀kẹ̀ funfun àti aláwọ̀ omiró tàbí búlúù.

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé Yemọja máa ń fún àwọn olùsìn rẹ̀ àti àwọn tí wọ́n bá tẹ̀ lé e ní ọmọ nítorí pé òrìṣà yìí ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ ní ìkáwọ́ rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni ó máa ń fún àwọn olùsìn rẹ̀ ní ọmọ. Èyí ni ó mú kí àwọn Yorùbá gbà láti máa tẹ̀lé òrìṣà Yemọja, tí wọ́n sì ń bọ ọ́ ní gbogbo ìgbà. Wàyí ò, àwọn àwòrò Yemọja máa ń bọ ọ́ nígbà tí ẹ̀kún omi bá wáyé, pàápàá ní àsìkò àrọ̀ọ̀dá òjò.

Àwọn ọlọ́kọ̀ ojú omi máa ń bọ Olókun tí wọ́n gbà pé òun ni Yemọja fi ṣe àkóso inú omi òkun, wọ́n sì máa ń bọ Ọlọ́sà tí ó ń ṣe àkóso omi Ọ̀sà. Èyí já sí pé Yemọja ni ó jẹ́ olórí àwọn òrìṣà omi, ìbáà ṣe òkun, ọ̀sà tàbí àwọn odò ńlá àti odò kéékèèké yòókù. Àwọn apẹja náà máa ń bọ Ọlọ́sà àti Olókun kí wọ́n lè fún wọn ní ẹja pa, kí wọ́n sì lè fẹ́ kí ìjì dáwọ́ dúró, kí wọ́n le rí ẹja pa nínú omi. Wàyí ò, ègbo ni oúnjẹ pàtàkì tí wọ́n fi máà ń bọ òrìṣà Yemọja.

## 4.5 Ṣànpọ̀nná

Ṣànpọ̀nná jẹ́ òrìṣà pàtàkì kan tí àwọn Yorùbá máa ń bọ. Òrìṣà yìí kan náà ni wọ́n ń pè ní *"Ọbalúayé"*. Èyí tí a lè túmọ̀ sí Ọba Olú Ayé tàbí tí a lè pè ní Ọba tí ó sì tún jẹ́ ọba nínú ayé. Òrìṣà yìí ni ó máa ń fi ìbínú Olódùmarè hàn, ó sì máa ń mú kí ọkàn àwọn ènìyàn wárìrì fún ìbẹ̀rù. Ṣànpọ̀nná yìí ni ó máa ń dá sẹ̀ríà fún àwọn oníwà burúkú nípa fífi ìlẹ̀ẹ́gbóná bá wọn jà. Nígbà mìíràn, wọ́n lè pè é ní *'Ilẹ̀ẹ́gbóná'*, bẹ́ẹ̀ ni òun yìí kan náà ni wọ́n máa ń pè ní *'baba'*. Òun yìí kan náà ni wọ́n ń pè ní *'Olóde'* nígbà mìíràn.

Ṣànpọ̀ná kórìíra iró pípa tàbí èké ṣíṣe. Kò fi ara mọ́ lílo òògùn olóró àti òògùn búburú. Ìdájọ́ rẹ̀ jẹ́ ìdájọ́ aláṣẹ èyí tí a gbọ́dọ̀ fi ara mọ́ pẹ̀lú ọ̀yàyà àti inú dídùn, ọpẹ́, láìsí àtakò tàbí irúnú. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń pè é *'Alápadúpẹ́'*. Nítorí náà, bí Ṣànpọ̀nná bá pa ènìyàn, wọn kò gbọdọ̀ dárò tàbí sunkún ẹni náà, bẹ́ẹ̀ ni àwọn àwòrò ni yóò kó ẹrù rẹ̀, tí wọn yóò sì sin òkú rẹ̀ sínú igbó burúkú tàbí igbó orò.

Àwọn ènìyàn gbàgbọ́ pé aṣọ pupa ni ó máa ń wọ̀ àti pé ó sábà máa ń kiri nínú òòrùn ọ̀sángangan. Nítorí náà, wọ́n máa ń kìlọ̀ fún àwọn ènìyàn láti má wọ aṣọ púpa tàbí rìn nínú oòrùn lọ́sàn-án gangan, pàápàá àwọn aláboyún, kí wọ́n máa baà rí ìbínú rẹ̀.

Ojúbọ òrìṣà Ṣànpọ̀nná máa ń sábà wà ní orí òkítì lẹ́yìn Ìlú níbì tí wọn yóò gbé agbada ẹlẹ́nu ńlá kan sórí rẹ̀; bẹ́ẹ̀ ni lẹ́gbẹ̀ẹ́ agbada yìí ni ọwọ̀ tàbí ìgbálẹ̀ kan tí a fi koríko ọ̀ṣẹ́pòtu ṣe yóò wà, èyí tí a kùn ní osùn.

Nítorí pé ní àkókò ìgbà ẹ̀ẹ̀rùn tàbí ìgba ooru ni àìsàn Ṣànpọ̀nná sábà máa ń yọjú, wọ́n máa ń pè é ní *'Ilẹ̀ẹ́gbóná'*, wọn kì í sì í dárúkọ rẹ̀ ní àsìkò yìí, ìyẹn ní oṣù kejì sí oṣù kẹrin ọdún. Ìdí nìyí tí wọ́n ń sọ nípa rẹ̀ pé aṣòroópè lẹ́ẹ̀rùn ni. Àmì ìdámọ̀ rẹ̀ ni osùn, àti ọwọ̀ ti a fi ewé ọparun tí a kùn láwọ̀ pupa dì. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ agbègbè ni wọ́n gbé máa ń bọ òrìṣà Ṣànpọ̀nná. Wọ́n ń bọ ọ ní Ìlú Ìbàdàn, Abẹ́òkúta, Ọ̀yọ́, Ìjẹ̀bú, Óṣogbo, Ilá, Ìjẹ̀ṣà, Òǹdó àti ní Èkó pẹ̀lú.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Lára àwọn Òrìṣà pàtàkì Yorùbá mìíràn ni a tún mẹ́nubà nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín kẹrin yìí. Àwọn ni Ṣàngó, Ẹ̀là, Òrìṣà-oko, Yemọja àti Ṣànpọ̀nná. Àwọn òrìṣà wọ̀nyí ní iṣẹ́ tí Olódùmarè fi rán wọn, bẹ́ẹ̀ ni àwọn Yorùbá kì í mú ọ̀kankan nínú wọn ní yẹpẹrẹ.

A ṣe àlàyé díẹ̀ lórí irú ẹni tí Ṣàngó jẹ́ àti bí ó ṣe di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ ní Ọ̀yọ́ Ilé. A kò ṣàìṣe àlàyé lórí ìbáṣepọ̀ àti ìbátan tí ó wà láàrín òrìṣà Ẹ̀là àti Ọ̀rúnmìlà ní ìgbà ìwàṣẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni ipa tí òrìṣà-oko kó nínú ìgbáyégbádùn àti ìdàgbàsókè Ìlú, tí wọ́n sì sọ ọ́ di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ títí ayé. A wo òrìṣà Yemọja gẹ́gẹ́ bí òrìṣà tí ń ṣe àkoso àwọn odò ńláńlá, òkun àti ọ̀sà pàápàá. Ní ìkẹyìn, a ṣe àlàyé irú òrìṣà tí Ṣànpọ̀nná jẹ́ àti ìbátan rẹ̀ pẹ̀lú àwọn òrìṣà Yorùbá yòókù. A rí ìwà Ṣànpọ̀nná bí ó ṣe le tó àti pé ẹni tí kò bá ti kọjá ààyè rẹ̀ le bá ojúrere rẹ̀ pàdé.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣàlàyé lẹ́kùn-únrẹ́rẹ́ ohun tí o mọ̀ nípa òrìṣà Ṣàngó.
2. Irú òrìṣà wo ni Ẹ̀là àti pé kín ni Ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàrín òun àti Ọ̀rúnmìlà.
3. Kín ló dé tí òrìṣà Ṣànpọ̀nná ṣe gbóná girigiri bẹ́ẹ̀ àti pé ǹjẹ́ o rò pé ó yẹ kí wọ́n máa bọ irú òrìṣà yìí?
4. Ṣe àlàyé bí wọ́n ṣe ń bọ Ṣànpọ̀nná àti Ṣàngó ní Ìlú rẹ̀.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Dáramọ́lá, O. & Jẹ́jẹ́, A. (2014). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn Oníbọn-Òjé Press.

Ologundudu, D. (2008). *The Craddle of Yorùbá Culture,* U.S., Center for Spoken Words/Institute of Yorùbá Culture.

Òjó, J.A. (1966). *Yorùbá Culture:* London, University of London Press.

Awolalu, J.O. & Dopamu, P.A. (1979). *West African Traditional Religion,* Ìbàdàn, Oníbọn-oje Press and Book Industries (Nig.) Ltd.

## MÓDÙ KEJÌ: ÀWỌN ẸKA ÀṢÀ ŃLÁŃLÁ YORÙBÁ

## ÌPÍN KARÙN-ÚN: ÀṢÀ ÌGBÉYÀWÓ LÁÀRÍN ÀWỌN YORÙBÁ

***Àkóónú***


1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ìlànà Ìgbéyàwó Yorùbá

4.2 Ìfojúsóde

4.3 Iṣíhùn tàbí Ìjọ́hẹn

44 Ìtọrọ àti Ìdána

4.5 Ìpalẹ̀mọ́ àti Ìgbéyàwó

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Ìgbéyàwó ṣe pàtàkì ní ààrìn àwọn Yorùbá. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ohun tí ó kárí ayé ni àṣà yìí, àwọn ìlànà ìgbéyàwó máa ń yàtọ̀ láti orílẹ̀-èdè sí orílẹ̀-èdè àti láti àwùjọ kan sí òmíràn. Bákan náà ni ìtọ́jú oyún àti ọmọ máa ń yàtọ̀ láti agbègbè kan sí èkejì.

Ọmọ bíbí ṣe kókó láàrín àwọn Yorùbá bẹ́ẹ̀ ni èyí ló mú kí ó ṣe pàtàkì yálà fún ọ̀dọ́mọkùnrin tàbí fún ọ̀dọ́mọbìnrin láti ṣe ìgbéyàwó. Bí Yorùbá bá ti ń dàgbà, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò máa ronú ọjọ́ iwájú wọn nípa ọ̀rọ̀ ìgbéyàwó. Èyí nìkan kọ́, bí a bá ṣe ìgbéyàwó tán, àdúrà pé kí ìyàwó finú ṣoyún, kí ó fẹ̀yìn gbọ́mọ pọn ni ó kù. Bí àdúrà yìí náà bá ti gbà, ó tún ku bí a ó ṣe tọ́jú ọmọ náà tí yóò fi ya ọmọ rere nígbà tí ó bá dàgbà tán.

Àwọn nǹkan wọ̀nyí ni a gbìyànjú láti ṣe àlàyé nínú ìpín yìí gẹ́gẹ́ bí Yorùbá ṣe máa ń ṣe é ní ṣíṣẹ̀-ntẹ̀lé títí gbogbo nǹkan yóò fi gún régé lọ́jọ́ iwájú.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Èròǹgbà ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ni:

- Láti jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ mọ pàtàkì àṣà Yorùbá nípa ìgbéyàwó.
- Kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti òǹkàwé mọ àwọn ètò tí Yorùbá máa ń ṣe fún àtigbéyàwó.
- Láti mú kí á mọ pàtàkì ọmọ bíbí lẹ́yìn ìgbéyàwó àti bí wọ́n ṣe ń tọjú ọmọdé.
- Kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìrírí nípa àwọn ètò tí Yorùbá ń gbà sọ ọmọ lórúkọ láyé àtijọ́.
- Láti mú kí àwọn òǹkàwé tàbí akẹ́kọ̀ọ́ ní òye irú orúkọ tí Yorùbá ń sọ ọmọ àti ìdí rẹ̀.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Kín ni pàtàkì ìyàwó tàbí ọkọ níní ní ayé àtijọ́ àti lóde òní?
2. Àwọn ọ̀nà wo ni Yorùbá máa ń gbà palẹ̀mọ́ fún ìgbéyàwó láyé àtijọ́ àti lóde òní?
3. Ǹjẹ́ orúkọ ọmọ ní nǹkan án ṣe lórí ìgbésí ayé ọmọ láyé àtijọ́ àti ní àkókò yìí?
4. Kín ni ìtumọ̀ àwọn orúkọ tí àwọn òbí rẹ̀ sọ ọ́ ní ọjọ́ ti wọ́n fún ọ lórúkọ?

## 4.0 Idánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìlànà Ìgbéyàwó Yorùbá

Ó ṣe pàtàkì láti pé àkíyèsí wa sí pàtàkì ọmọ láàrín àwọn Yorùbá títí di òní olónìí. A ó rí i pé ọmọ bíbí kì í ṣe nǹkan yẹpẹrẹ láwùjọ Yorùbá bẹ́ẹ̀ ẹni tí kò bá ní ìyàwó, kò le bímọ lọ́nà ẹ̀tọ́ àti ti ọmọlúàbí. Nítorí náà, bí a bá ń wúre fún ọ̀dọ̀mọkùnrin tàbí ọ̀dọ́mọbìnrin pé yóò ṣe àǹfààní láyé, a kò gbọdọ̀ gbàgbé pé ibi tí àǹfààní ti bẹ̀rẹ̀ ni ibi kí wọ́n ṣe ìgbéyàwó.

Láyé àtijọ́, bí ọ̀dọ́mọkùnrin tàbí ọ̀dọ́mọbìnrin kan bá ti dàgbà ṣùgbọ́n tí kò tí ì ní àfẹ́sọ́nàn nígbà tí àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ bá ti ń fẹ́ ìyàwó wọlé, ojú kò ní í kúrò lára irú ẹni bẹ́ẹ̀, àwọn ènìyàn àwùjọ yóò sì máa bi irú ẹni bẹ́ẹ̀ ní oríṣiríṣi ìbéèrè nípa àtiní ìyàwó tàbí àtilọ́kọ. Ní ayé àtijọ́, ènìyàn kì í ṣàdédé ya àpọ́n bí kò bá jẹ́ pé àgùtàn ti bu irú ẹni bẹ́ẹ̀ jẹ. Bí ènìyàn kan bá tilẹ̀ ya àpọ́n, irúfẹ́ ènìyàn bẹ́ẹ̀ máa ń gbìyànjú láti fi ìlú sílẹ̀ nítorí ìtìjú, pàápàá tí ẹnu bá ń pọ̀jù lára rẹ̀. Ṣùgbọ́n lóde òní, ènìyàn kan le ya àpọn láìjẹ́ pé àgùtàn ti bù ú jẹ nítorí pé *"bí ó ṣe wuni la ń ṣe ìmàle ẹni"* ni ọ̀rọ̀ dà báyìí; àwòsóju ni a sì máa ń wo olè ilé.

Láìdéènà pẹnu, àwọn ìlànà kán wà tí àwọn Yorùbá máa ń tẹ̀lé nípa ìgbéyàwó láti ìgbà ìwáṣẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ síwájú, ọkùnrin gbọ́dọ̀ gbé ìyàwó, bẹ́ẹ̀ obìnrin gbọ́dọ̀ lọ sí ilé-ọkọ. Láyé ìgbà náà, ọkùnrin ni ó sábà máa ń kọnu ìfẹ́ sí obìnrin àti pé àwọn òbí ní í sábà fẹ́ aya fún ọmọ wọn, bẹ́ẹ̀ ni àwọn náà ló máa ń fa ọmọbìnrin fún ọkọ nítorí pé ọmọ kò ní àṣẹ kankan lórí ẹni tí òbí rẹ̀ bá fẹ́ fẹ́ fún un tàbí ẹni tí wọ́n bá fẹ́ fà á fún.

## 4.2 Ìfojúsóde

Oríṣìríṣì ọ̀nà ni àwọn Yorùbá máà ń gbà láti fojúsóde láti rí ọmọbìnrin tí wọ́n fẹ́ fẹ́ fún ọmọ wọn. Nígbà mìíràn, àwọn Yorùbá máa ń fẹ́ ọmọ tí ó wà nínú oyún fún ọmọ ọwọ́, ìbáà jẹ́ obìnrin tàbí ọkùnrin lérò pé oyún inú náà lè jẹ́ ẹni tí yóò fẹ́ ọmọ ọwọ́ yìí. Bí èrò wọ́n bá rí bẹ́ẹ̀, a jẹ́ pé ibi tí wọ́n fẹ́ gbin obì sí, tí obì hù níbẹ̀, kí wọ́n máa tún ìdí rẹ̀ ṣe ni ó kù.

Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, bí ọmọkùnrin bá ti bàlágà, àwọn òbí rẹ̀ yóò ti máa fi ojú sóde bóyá ó ṣe é ṣe kí wọ́n rí ọmọbìnrin kan tí wọn yóò fẹ́ fún ọmọ wọn. Ọmọkùnrin náà yóò ti máa tún ara ṣe, yóò máa ṣe oge tí kò ṣe látẹ̀yìnwá. Ó le máa wẹ̀ nígbà méjì tàbí mẹ́ta ní ọjọ́ kan. Wàyí ò, nígbà tí ó bá fi ojú kan wúńdíá kan tí ó rẹwà, ara rẹ̀ yóò máa wá rìrì, ìfẹ́ ọmọbìnrin náà yóò sì kó sí í lórí. Ṣùgbọ́n ṣá o, ọmọkùnrin yìí kò ní í lè lọ gaara láti bá ọmọbìnrin sọ̀rọ̀. Nígbà yìí ni ó wá kan iṣẹ́ alárenà.

Alárenà yìí ni yóò ṣe àwọn ìwádìí pàtàkì kan láàárín àwọn ẹbí méjèèjì, bẹ́ẹ̀ ni àwọn ìwádìí wọ̀nyí lè dá lórí bóyá àwọn ìdílé wọ̀nyí kò ní àrùn burúkú kan tí ń bá wọn jà tàbí kí wọ́n jẹ́ ìdílé onígbèsè. Àbọ̀ ìwádìí yìí ni yóò fi hàn bóyá àwọn ọmokùnrin àti ọmọbìnrin yìí lè fẹ́ ara wọn nísụ lọ́kà gẹ́gẹ́ bí tọkọtaya tàbí wọn kò ní í lè fẹ́ ara wọn. Wọ́n tún le ṣe ìwádìí lọ́wọ́ Ọ̀rúnmìlà bóyá ìgbé-ayé àwọn wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bí tọkọtaya yóò tùbà-tùṣẹ lọ́jọ́ iwájú tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́. Wàyí ò, bí Ifá wọ́n bá fọre, a jẹ́ pé ètò àti ìgbésẹ̀ yòókù yóò máa tẹ̀síwájú nìyẹn.

Láyé àtijọ́, ọkùnrin lè gba obìnrin abilékọ lọ́wọ́ ọkọ rẹ̀. Èyí sábà máa ń wáyé bí ọkọlóbìnrin bẹ́ẹ̀ kò bá lè ṣe ojúṣe rẹ̀ bí ó ti yẹ, tàbí kí ìyàwó jẹ́ aláìnítẹ̀ẹ́lọ́rùn àti olójúkòkòrò obìnrin. Bí àpẹẹrẹ, obìnrin mìíràn lè sọ pé ọkọ tí ó fẹ́ kọ̀ sílẹ̀ kò bá a ṣe òkú ìyá tàbí bàbá rẹ̀, kí ó sì ti ipa bẹ́ẹ̀ sá tọ ọkùnrin mìíràn lọ. Ayé òde-oní ni èyí ń ṣẹlẹ̀. Láyé ọjọun, àìrọ́mọbi ni ìdí pàtàkì tí obìnin fi ń kọ ọkọ.

Ìlànà mìíràn ni pé ọkùnrin le fẹ́ ìyàwó nípa opó síṣú. Èyí máa ń wáyé bí baba kan bá kú, tí àkọ́bí ọmọ baba náà tí ó ti bàlágà jogún ọ̀kan nínú àwọn ìyàwó baba rẹ̀, pàápàá èyí tí ó kéré jù. Bí bàbá aláìsí náà kò bá ní ọmọkùnrin tí ó ti bàlágà, àbúrò aláìsí náà tí ó jẹ́ ọkùnrin le jogún ìyàwó ẹ̀gbọ́n rẹ̀.

Ọ̀nà mìíràn tí Yorùbá tún fi máa ń fẹ́ ìyàwó lọ́jọ́ ọjọ́un ni ti *'gbàmí-o-ràmí'*, èyí tí ó máa ń ṣẹlẹ̀ nígbà tí àwọn ẹbí aláìsàn kan bá ṣe ìpinnu pẹ̀lú oníṣègùn pé bí oníṣègùn náà bá lè tọ́jú ọmọbìnrin wọn, kí ó fi ṣe aya. Bí ó bá rí bẹ́ẹ̀, bí aláìsàn náà bá gbádùn, ó di ìyàwó oníṣègùn náà nìyẹn.

## 4.3 Ìṣíhùn tàbí Ìjọ́hẹn

Lẹ́yìn ìgbà tí àdéhùn bá ti wáyé pé ọ̀dọ́mọkùnrin àti ọ̀dọ́mọbìnrin bá ti gbà láti dì tọkọtaya, ìgbésẹ̀ tí ó kàn ni pé kí ọkọ fún ìyàwó àfẹ́sọ́nà rẹ̀ ní owó *'ìjọ́hẹn'* tàbí *'Ìṣíhùn'*. Lẹ́yìn ìgbà tí alárenà bá ti mú ojú ajá kojú ajá tan, tí ó ti mú ojú ìyàwó àti ọkọ kan ara wọn tán, ọmọkùnrin àti ọmọbìnrin yóò bẹ̀rẹ̀ sí i pàdé lóòrèkóòrè níbi tí ó bá wù wọ́n. Lẹ́yìn èyí ni alárenà àti àwọn òbí ọmọkùnrin yóò lọ tọrọ ọmọbìnrin lọ́wọ́ àwọn òbí àti ẹbí ìyàwó àfẹ́sọ́nà rẹ̀.

## 4.4 Ìtọrọ àti Ìdána

Lẹ́yìn tí ọmọbìnrin bá ti gbà pátápátá pé òun yóò fẹ́ ọmọkùnrin yìí, ọmọkùnrin yóò lọ sọ fún baba rẹ̀ pé òun ti rí òdòdó pupa kan, tí ó lẹ́wà ní ilé Lágbájá tàbí ní ọ̀dẹ̀dẹ̀ Làkásegbe àti pé òun fẹ́ já a. bàbá rẹ̀ yóò bèèrè lọ́wọ́ ọmọ rẹ̀ bóyá òdódó náà ṣe é já tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́, ọmọkùnrin yóò sì dá baba rẹ̀ lóhùn pé àwọn ti jọ sọ̀rọ̀ púpọ̀, bẹ́ẹ̀ ni àwọn ti pinnu láti fẹ́ ara àwọn. Èsì yìí ni yóò fún bàbá rẹ̀ ní ìwúrí láti lè lọ bá àwọn àgbà àdúgbò tí yóò sì bẹ̀ wọ́n láti tẹ̀ lé òun lọ́ sí ilé àwọn òbí àti ẹbí àfẹ́sọ́nà ọmọ rẹ̀ náà. Nígbà yìí ni wọn yóò ránṣẹ́ sí àwọn òbí ọmọbìnrin yìí, wọn yóò sì jí lọ ní kùtù hàì, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò sọ fún àwọn òbí ìyàwó àfẹ́sọ́nà wọn pé kí wọ́n gba àwọn lááyè láti fẹ́ ọmọ wọn fún ọmọ àwọn láti fi ṣe aya. Ọ̀rọ̀ yìí kò níí bá baba ọmọbìnrin náà lábo nítorí pé òun náà ń rí ìrìn-ẹsẹ̀ ọmọ rẹ̀ tó ń ṣe wọ́kọwọ̀kọ kí ó tó di ọjọ́ yẹn. Nítorí náà, baba ìyàwó yìí yóò fèsì fún baba ọmọkùnrin tí ó fẹ́ fẹ́ ọmọ rẹ̀ pé ìgí kan kì í dágbó ṣe àti pé òun yóò lọ sọ fún àwọn ẹbí òun nípa rẹ̀, yóò sì sọ pé kí wọ́n wá pàdé ẹbí òun ní àkókò tàbí ọjọ́ báyìí, báyìí. Ní ọjọ́ tí wọ́n bá dá ni wọn yóò pàdé láti jíròrò bẹ́ẹ̀ ni níbẹ̀ ni wọn yóò ti tọrọ ọmọbìnrin náà.

Lẹ́yìn ìtọrọ yìí ni ọjọ́ Ìdána. Ọjọ́ yìí máa ń jẹ́ ọjọ́ ayọ̀ àti ọjọ́ àríyá bẹ́ẹ̀ ni àwọn obìnrin nílé ọmọkùnrin àti ilé ọmọbìnrin yóò pagbo eré. A kò ní í ṣàìménubà á pé àárọ̀ tàbí ìrọ̀lẹ́ pẹ̀sẹ̀ ni wọ́n sábà máa ń pàtẹ ayẹyẹ yìí sí ní ilé ẹbí ọ̀dọ́mọbìnrin bẹ́ẹ̀ ni àwọn ilé ọ̀dọ́mọkùnrin yóò kó àwọn nǹkan ìdána sílẹ̀. Lára àwọn ohun ìdána yìí ni oyin, obì,

ìrèké, àádùn, orógbó, ataare, epo pupa, onírúurú èso igi àti ọtí àti ẹmu tí wọn yóò sì iṣú ńkọ́? máa fi ọ̀kọ̀ọ̀kan ṣe àdúrà fún ẹbí kìnní àti ẹbí kejì. Níbí ni wọn yóò ti ka èèwọ̀ ẹ̀bí wọn fún ẹbí ọkọ láti fi ṣe ìkìlọ fún wọn. Bí àpẹẹrẹ, wọ́n lè sọ pé wọn kì í na ọmọ wọn, ebi kì í pa ọmọ wọn, ọmọ wọn kìí jẹ gbágùdá, kì í jẹ kókò, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Lẹ́yìn èyí ni ẹni tí ó dàgbà jù nínú ẹbí yóò fa ìyàwó le ẹni tí ó dàgbà jù nínú ẹbí ọkọ lọ́wọ́. Wàyí ò, ó ṣe pàtàkì láti sọ pé àwọn ẹbí ọkọ yóò san owó ìdána. Èyí sì máa ń yàtọ̀ láti agbègbè kan sí ekejì.

## 4.5 Ìpalẹ̀mọ́ àti Ìgbéyàwó

Lẹ́yìn ètò ìdána ni àwọn ẹbí méjèèjì yóò fi ẹnu kò láti dájọ́ ìgbéyàwó, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n gbọdọ̀ lọ ṣe ìbéèrè tàbí ìwádìí lọ́wọ́ Ifá. Bí Ifá bá ti fi àṣẹ sí ọjọ́ tí wọ́n dá náà, lẹ́yìn èyí ni wọn yóò máa ṣe ìpalẹ̀mọ́ ìgbéyàwó. Ìyàwó yóò máa palẹ̀ mọ́ díẹ̀díẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni ọkọ náà yóò máa bá ìyàwó rẹ̀ palẹ̀mọ́ nípa fífún un ní owó tí yóò fi ra aṣọ àti àwọn nǹkan oge mìíràn. Lára ìpalẹ̀mọ́ tí ìyàwó yóò ṣe ni láti lọ máa kọ́ bí wọ́n ṣe ń sun ẹkún ìyàwó lọ́dọ̀ àwọn ìyàwó ilé nínú ẹbí rẹ̀. Ìyàwó lè fin apá, ojú, ìbàdí, ọrùn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Èyí ni láti bu ẹ̀wà kún un ní àkókò yìí. Ẹkún ìyàwó yìí máa ń wáyé nígbà tí ìyàwó bá ń ronú nípa àwọn ìṣòro tí ó le bá pàdé nílé ọkọ lọ́jọ́ iwájú.

Ọjọ́ ìgbéyàwó yìí máa ń jẹ́ ọjọ́ ayọ̀, ìdùnnú àti ọjọ́ mánigbàgbé fún ẹbí méjèèjì àti àwùjọ lápapọ̀. Ìlù, orin, ijó ni àwọn ìyàwó ilé yóò fi sin ọmọbìnrin náà dé ilé ọkọ rẹ̀ ní ọwọ́ ìrọ̀lẹ́ mọ́ alẹ́ ọjọ́ náà.

Ó ṣe pàtàkì láti tọ́ka sí i pé ọ̀rọ̀ ìbálé obìnrin ṣe pàtàkì láyé àtijọ́. Èyí ni pé obìnrin tí kò bá tí ì mọ ọkùnrin ṣaájú àsìkò yìí máa ń gbayì-gba-ẹ̀yẹ nílé ọkọ nítorí pé kò tí ì di kòròǹfo. Oríṣiríṣi ẹ̀bun ni irú obìnrin bẹ́ẹ̀ máa ń gbà lọ́wọ́ àwọn ẹbí àti ọ̀rẹ́ ọkọ fún irú ìdágáǹjíá bẹ́ẹ̀. Ní ìdàkejì ẹ̀wẹ̀, bí ìyàwó bá ti mọ ọkùnrin tẹ́lẹ̀ ṣaájú ọjọ́ ìgbéyàwó yìí, ọ̀rọ̀ ìtìjú pátápátá gbáà ni fún ọmọ bẹ́ẹ̀ àti àwọn òbí rẹ̀, ní pàápàá, ìyá rẹ̀.

Ní ìparí, a ó ṣàkíyèsí pé ìyípadà ti de bá ìlànà àti ètò ìgbéyàwó lóde òní. Àṣà pé a ń yan ọkọ fún ọmọ ọjọ́ kan tàbí láti inú oyún ti kásẹ̀ nílẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni àṣà à ń wá alárenà tí yóò máa ṣe agbódegbà láàrin ọ̀dọ́mọkùnrin àti ìyàwó àfẹ́sọ́nà rẹ̀ ti di ohun ìgbàgbé. Lóde òní, kì í sábà sí ìwádìí kan gúnmọ́ lọ́wọ́ Ifá tàbí níbikíbi kí tọkọtìyàwó tó fẹ́ ara wọn. Bóyá, ìdí nìyí tí ọ̀pọ̀ ìgbéyàwó òde-òní ṣe ń forí ṣánpọ́n. Ìlànà ẹ̀sìn ìgbàlódé tilẹ̀ ti kásẹ̀ àwọn ètò àti ìlànà àtijọ́ nílẹ̀ pátápátá.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín kẹrin yìí ni a ti wo àṣà ìgbéyàwó láàrín àwọn Yorùbá láyé àtijọ́. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a kàn fáàrà lórí ìlànà ìgbéyàwó níbi ni, síbẹ̀síbẹ̀, ọ̀pọ̀ ìyípadà ni ó ti dé bá àṣà ìgbà ìwásẹ̀ yìí.

Níbí ni a ti wo ìṣepàtàkì ìgbéyàwó káàkiri àgbáyé àti bí àṣà ìgbéyàwó Yorùbá ti ṣe é mú yangàn tó láyé ìgbàanì. Ó ṣeni láàánú pé àwọn ẹ̀sìn ìgbàlódé àti ọ̀làjú ti mú kí iná àṣà yìí jó àjórẹ̀yìn. Kò sí pé a ń ṣe ìwádìí fínnífínní mọ́ kí á tó tẹsẹ tàbí tara bọ ìgbéyàwó mọ́ lóde òní. Bí a kò tilẹ̀ lọ sí ọ̀dọ Barapetu, tí a kò lọ sí ọ̀dọ̀ àwọn wòlíì tàbí Ìmáámù láti ṣe ìwádìí ètò Ọlọ́run yìí, ó yẹ kí á mọ̀ pé àwọn ìwádìí kan tún ń bẹ tí ó yẹ kí á tẹ̀lé kí a lè mọ ọjọ́ iwájú ìgbéyàwó wa.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣe àlàyé lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́ àwọn ìlànà àti ètò ìgbéyàwó láàrín àwọn Yorùbá ní ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀.
2. Ṣàlàyé ohun tí o mọ̀ ní ìfojúsóde àti ìyípadà tí ó dé bá a ní òde òní.
3. *"Ìbálé kì í ṣe ohun àmúyangàn lóde òní"*. Dá sí ọ̀rọ̀ náà.
4. Àwọn àtúnṣe wo ni o rò pé ó yẹ fún ìlànà ìgbéyàwó tí ayé àtijọ́ àti tóde òní?
5. Sọ àwọn ètò ìgbéyàwó tí ó máa ń wáyé ní ìlú rẹ.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Owólabí, K. *et al* (2015). *Jẹ́ ká Bára Wa Sọ̀rọ̀ Ní Yorùbá, A Multidimentional Approach to the Teaching and Learning of Yorùbá As a Foreign Language.* Bloomington, Indiana, NALRC Press.

Dáramọ́lá, O. àti Jẹ́jẹ́, A. (2014). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá*, Ìbàdàn, Oníbọn-òjé Press and Book Industries (Nig.). Ltd.

Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*, Ìbàdàn, Gavima Press Ltd.

## MÓDÙ KẸTA: ÀWỌN ÀṢÀ YORÙBÁ KÉÉKÈÈKÉÉ

## ÌPÍN KÌNNÍ: ÌTỌ́JÚ OYÚN, ỌMỌ BÍBÍ ÀTI ÌTỌ́JÚ ỌMỌDÉ

***Àkóónú***


1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ìtọ́jú Aláboyún

4.2 Bí a ti n de oyún

4.3 Ọmọ Bíbí

44 Ilà Kíkọ

4.5 Ìtọ́jú Ọmọdé

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Nínú ìpín yìí ni a ti ṣe àlàyé àwọn ohun tí ó kàn ní ṣíṣe lẹ́yìn tí ìyàwó bá ti dé ilé ọkọ rẹ̀ tán, tí òun náà sì dì onílé. Ohun tí ó kù náà ní pé kí ìyàwó finú ṣoyún, kí ó sì fi ẹ̀yìn pọnmọ.

Ní kété tí ọkọ bá ti mọ̀ pé ìyàwó òun ti fẹ́rakù ni yóò ti fi tó baba àti ìyá rẹ̀ létí, bẹ́ẹ̀ ni ìtọ́jú oyún náà yóò bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu. Oríṣiríṣi ọ̀nà ni wọ́n máa ń gbà tọ́jú oyún títí ìyàwó náà yóò fi bímọ. Wọn yóò ṣe onírúurú àsèjẹ fún aboyún náà kí oyún náà lè dúró, kí ó má báa wálẹ̀ láìpé ọjọ́. Wọn yóò fún un ní mímu, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò fún un ní wíwẹ̀. Báyìí ni wọn yóò máa tọ́jú aboyún àti ọmọ inú rẹ̀ títí yóò fi di ọjọ́ ìkúnlẹ̀.

Ní ọjọ́ ìkúnlẹ̀ wàyí ò, onírúurú ìtọ́jú ni wọn yóò ṣe fún abiyamọ náà, kí o lè baà sọ̀ láyọ̀. Bẹ́ẹ̀ ni bí obìnrin náà bá ti sọ láyọ̀, gbogbo ilé ni yóò máa kí tọkọ tìyàwó kú oríire, tí wọn yóò sì tẹ̀síwájú nínú ìtọ́jú ìyá ọmọ tuntun àti ọmọ rẹ̀ náà. Lẹ́yìn tí ó bá ti sọ̀ láyọ̀, àwọn ìgbésẹ̀ tí ó kàn ni kí wọ́n kọ ọmọ náà ní ìlà abẹ́ àti ilà ojú. Ẹ̀yí lè jẹ́ bí oṣù kan lẹ́yìn ìbímọ.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lára èròǹgbà ìpín yìí ni:

- Láti jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ mọ̀ nípa ìtọ́jú aboyún ní àkókò náà.
- Kí akẹ́kọ̀ọ́ tí kò tíì dé irú ipò yìí lè múra sílẹ̀ fún irú àkókò báyìí.
- Láti le mú kí akẹ́kọ̀ọ́ mọ bí abiyamọ ṣe ń tọ́jú ọmọdé, kí ara rẹ̀ lè le koko.
- Kí akẹ́kọ̀ọ́ le mọ ìdí tí àwọn Yorùbá ṣe ń kọ ilà abẹ́ àti ti ojú láyé ìgbàanì.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Bá wo ni àwọn Yorùbá ṣe ń tọ́jú aboyún láyé àtijọ́ àti lóde òní?
2. Àwọn ọ̀nà wo ni àwọn Yorùbá ń gbà de oyún ní ayé àtijọ́?
3. Kín ni ìwúlò àṣà ilà kíkọ láyé àtijọ́ àti lóde òní?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìtọ́jú Aboyún

Ìmọ̀ nípa bí a ṣe ń tọ́jú aboyún ṣe pàtàkì púpọ̀ fún àǹfàànì àwọn ọ̀dọ́mọdé lọ́kùnrin àti lóbìnrin. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọ̀dọ́ wọ̀nyí ni kò tilẹ̀ ní òye bí oyún ṣe ń ta le ọmọbìnrin, ní pàápàá jù lọ bí wọ́n ṣe le mọ̀ bí oyún bá ti dúró sí wọn lára. Àwọn mìíràn kì í ṣe àkíyèsí kankan àfi ìgbà tí inú wọ́n bá ń yọ síta ní wọn yóò tó mọ̀ pé wọ́n ti fẹ́ra kù.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀nà ni obìnrin le gbà mọ̀ pé oyún ti bá òun lálejò yàtọ̀ sí ìgbà tí ikùn bá ń yọ síta. Ọ̀nà kìnní ni pé ọmọbìnrin bẹ́ẹ̀ yóò máa tòògbé púpọ̀ jù láìṣe alẹ́ tàbí òru. Èyí nìkan kọ́, ọ̀nà ọ̀fun yóò máa rin obìnrin yìí, yóò sì máa síntọ́ káàkiri ilẹ̀. Obìnrin mìíràn lè má fẹ́ jẹun dáadáa mọ́ nítorí oúnjẹ jíjẹ yóò máa sú u láti jẹ, yóò sì máa rùn sí i. Ní pàtó, bí ọjọ́ bá ti ń gorí ọjọ́, ikùn obìnrin yìí yóò máa kùn díẹ̀díẹ̀, yóò sì máa tóbi sí i. Nígbà yìí ni àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí yóò jẹ́ kí obìnrin mọ̀ pé òun ti fẹ́rakù, ìyẹn ni pé òun ti lóyún.

### 4.2 Bí a ṣe ń de Oyún

Gbàrà tí wọ́n bá ti ṣe àkíyèsí pé oyún ti dúró sí obìnrin lára ni wọn yóò ti tọ babaláwo lọ fún ìtọ́jú tí ó bá yẹ. Àárọ̀ kùtùkùtù ni wọn yóò mú obì àti akèngbè ẹmu dání lọ sọ́dọ̀ babaláwo yìí láti jẹ́ kí ó mọ̀ pé àwọn fẹ́ kí ó bá wọn ṣe ìtọ́jú oyún náà, kí ó má baà wálẹ̀ láìpé ọjọ́.

Oríṣiríṣi nǹkan ni babaláwo yóò fi máa ṣe aájò aboyún yìí títí yóò fi bímọ. Bí àpẹẹrẹ, nígbà mìíràn, babaláwo le fi òròrò ẹyin adìẹ ṣe aájò fún aboyún èyí tí wọ́n lè fi há ibi kọ́lọ́fín kan títí di àkókò tí oṣù aboyún náà yóò pé, tí yóò sì bímọ wẹ́rẹ́, láìsí pákáleke kankan. Nígbà mìíràn, babaláwo le mú ẹyin òròrò, kí ó sè é mọ́ àwọn àgbo mìíràn, kí ó sọ fún aboyún náà pé kí ó dúró nínú ajádìí agbọ̀n, kí wọ́n bó ẹyin náà fún obìnrin náà jẹ. Lẹ́yìn èyí, wọn yóò máa retí akókò tí oṣù obìnrin aboyún náà yóò pé láti bímọ. Nígbà tí ó bá bímọ tán, onírúurú ìtọ́jú ni wọn yóò máa fún ọmọ tuntun àti ìyá rẹ̀. Bí wọ́n ṣe ń wẹ ọmọ, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò máa jó ìyá ọmọ náà lára pẹ̀lú omi gbígbóná. A kò gbọdọ̀ gbàgbé láti sọ pé títí di ìgbà tí aboyún yìí yóò fi bímọ, ó di èèwọ̀ fún un láti pín ẹyin adìẹ jẹ.

## 4.3 Ọmọ Bíbí

Gbàrà tí ọmọ tuntun bá ti jáde lábẹ́ obìnrin, ó di dandan kí wọ́n ta epo pupa sí ilẹ̀ ibẹ̀ láti fi wúre fún ọmọ tuntun náà pé ayé rẹ̀ yóò dẹ̀rọ̀ láti òwúrọ̀ di ọjọ́ alẹ́ rẹ̀.

Lẹ́yìn tí ọmọ bá jáde tán ni ohun tí a ń pè ní olubi ọmọ tàbí èkejì ọmọ gbọ́dọ̀ jáde kí ọkàn abiyamọ lè balẹ̀ nítorí pé bí olubi ọmọ yìí kò bá tí ì jáde, ẹni tí ó bímọ náà lè tipa bẹ́ẹ̀ jẹ́ Ọlọ́run nípè. Ṣùgbọ́n ṣá o, bí olubi ọmọ yìí kò bá tètè jáde, Yorùbá ní àwọn ohun tí wọ́n máa ń ṣe láti pè é jáde láìsí wàhálà.

Bí olúbi ọmọ náà bá ti jáde tán, wọ́n ní láti tọ́jú rẹ̀ dáadáa, wọn kò sì gbọdọ̀ jẹ́ kí ajá gbé e. Lẹ́yìn ìgbà tí a bá ti tọ́jú olubi ọmọ yìí tán, wọn yóò ṣe ètò láti wẹ ọmọ náà fún ìgbà àkọ́kọ́ ní ìgbésí ayé rẹ̀. Wọn yóò ṣe èyí pẹ̀lú omí gbígbóná, ọṣẹ dúdú àti kàn-ìn-kàn-ìn. Ó ṣe pàtàkì láti ṣe àlàyé pé wọ́n gbọ́dọ̀ wẹ ọmọ yìí kí ó mọ́ dáadáa nítorí pé bí wọn kò bá wẹ̀ ẹ́ mọ́ dáadáa, ara ọmọ náà lè máa rùn lọ́jọ́ iwájú. Lẹ́yìn tí a bá ti wẹ ọmọ náà mọ́ dáadáa tán, wọn yóò kùn un ní osùn, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò fi aṣọ dáradára wé e, bẹ́ẹ̀ ni ojú rẹ̀ nìkan ni ó gbọ́dọ̀ yọ sóde. Wọ́n gbọdọ̀ tọ́jú ìdodo ọmọ, èyí ni ibi tí òun àti olúbi ti pínyà. Tí wọ́n bá ti gé okùn ìdodo ọmọ náà, wọn yóò fi òwú wé e, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò máa fi òkúta gbígbóná jọ́ o láàárọ̀, lọ́sàn-án àti lálẹ́ títí tí okùn ìdodo náà yóò fi bọ́ sílẹ̀, tí wọn yóò sì tọ́jú rẹ̀ bí ó ṣe yẹ. Ó ṣe pàtàkì kí wọ́n tọ́jú ìdodo yìí, kí ó jinná wọnú dáadáa nítorí pé tí kò bá jinná dáadáa, nǹkan àmúwà rẹ̀ kò ní í ṣiṣẹ́ bí ó ti yẹ. Nítorí ìdí èyí, Yorùbá máa ń ṣe ìtọ́jú ọmọ dáadáa kí akùdé má baà bá àgọ́ ara rẹ̀ lọ́jọ́ iwájú.

## 4.4 Ilà Kíkọ

Ilà kíkọ jẹ́ àṣà tí ó ṣe pàtàkì láàrín àwọn Yorùbá ní ayé àtijọ́. Ilà kíkọ yìí pín sí ọ̀nà mẹ́ta. Ọ̀tọ̀ ni ilà abẹ́ dídá fún ọmọdébìnrin àti okó dídá fún ọmọdékùnirn, bẹ́ẹ̀ ni ọ̀tọ̀ ni ilà ojú fún tọmọdékùnrin àti obìnrin.

Yorùbá sábà máa ń kọlà fún ọmọ róbótó, tí kò tí ì ní ọjọ́ lórí. Nítorí náà, wọ́n máa ń kọlà fún ọmọ kí ó tó pé oṣù mẹ́ta tí a bí i sáyé.

Ilà kíkọ fún àwọn ọmọkùnrin jẹ́ dandan láàrin àwọn Yorùbá àti àwọn ẹ̀yà mìíràn ní ilẹ̀ Adúláwọ̀ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èyí kò pọn dandan àti pé ẹni tí ó bá wù ni ó le kọlà abẹ́ fún ọmọkùnrin. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọkùnrin Òyìnbó kì í kọlà

abẹ rárá. Nípa tí àwọn obìnrin, Yorùbá máa ń dá abẹ fún àwọn obìnrin nítorí pé wọ́n gbàgbọ́ pé nǹkan kan wà lábẹ obìnrin tí ó le di ọmọ lọ́wọ́ tí wọ́n bá fẹ́ bímọ àti pé orí ọmọ kò gbọdọ̀ kan nǹkan náà.

Ṣùgbọ́n sá, ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn, pàápàá àwọn elétò ìlera òyìnbó ni wọ́n ń sọ pé kò dára kí ọmọbìnrin máa dábẹ́ àti pé ìfìyàjẹni tí ó tó èyí kò sí. Nísinsinyìí, a tilẹ̀ ti rí àwọn Ẹgbẹ́ obìnrin kan tí wọ́n ń sọ pé èyí kò bá òfin mu àti pé àwọn tí ó bá ń ṣe bẹ́ẹ̀ ń tẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú ni. Wàyí ò, ìwà a ń kọlà abẹ tàbí a ń dábẹ́ fún ọmọbìnrin ti dínkù láàrín àwọn Yorùbá díẹ̀díẹ̀. Dípò èyí, wọ́n máa ń jọ́ abẹ́ fún àwọn ọmọbìnrin ni, ṣùgbọ́n àwọn ọmọkùnrin Yorùbá sì ń kọlà abẹ títí di òní olónìí.

## 4.5 Ìtọ́jú Ọmọdé

Bí a ṣe ń tọ́jú aboyún àti ọmọ tuntun jòjòló bẹ́ẹ̀ ni Yorùbá máa ń ṣe ìtọ́jú ọmọdé náà pẹ̀lú. A ó rí i pé àwọn ọmọdé tàbí màjèsín náà sì máa ń wà ní abẹ́ ààbò tàbí àkóso òbí fún ìtọ́jú àti ìtọ́sọ́nà. A ó ṣe àkíyèsí pé àwọn ọmọdé wọ̀nyí kò tí ì ní òye, ọgbọ́n tàbí ìrírí tí wọ́n fi le tọ́jú ara wọn, wọn kò tilẹ̀ ní owó láti ná fún ìlera ara wọn bí kò ṣe pé abẹ́ ààbò àwọn òbí wọn ni wọ́n sì wà. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, ewé àti egbò ni a fi máa ń tọ́jú àwọn ọ̀dọ́mọdé wọ̀nyí, bẹ́ẹ̀ ni oríṣiríṣi àgbo ni a máa ń lò fún wọn.

Nígbàkígbà tí ikùn ọmọdé bá bẹ̀rẹ̀ sí í ṣe wọ́bọ́wọ́bọ́, tí inú rẹ̀ sì ń kùn sùn-ùn-rùn-sùn, àgbo wọ́bọ́ ni wọn yóò ṣe fún irú ọmọ bẹ́ẹ̀, yóò sì sàn nínú àìsàn yìí. Ọmọ tí àìsàn jẹ̀díjẹ̀dí bá ń ṣe, tí kò rí ìgbẹ́ yà, tàbí ti ìdí rẹ̀ ń pariwo, àgbo jẹ̀díjẹ̀dí náà ni wọ́n yóò fún un tí yóò sì sàn. Àìsàn kan tún wà tí ó máa ń mú kí isan orí ọmọdé hàn síta ga-nga, tí àwùjẹ̀ irú ọmọ bẹ́ẹ̀ yóò lanu sílẹ̀ gẹrẹjẹ, ọmọ yìí yóò sì máa mí gúlegúle. Àìsàn yìí lè má jẹ́ kí irú ọmọ bẹ́ẹ̀ rí oorun sùn, yóò sì máa sọkún sáá. Bí irú èyí bá wáyé, wọn yóò tí mọ̀ pé àìsàn tí wọ́n ń pè ní ọ̀kà-orí tàbí oríjorí ni. Àgbo ọ̀kà orí ni wọn yóò se fún irú ọmọ bẹ́ẹ̀, tí àìsàn náà yóò sì kúrò lára ọmọ náà. Ọ̀ká orí yìí wọ́pọ̀ nínú àwọn àìsàn tí ó máa ń yọ aròbó lẹ́nu ṣùgbọ́n bí wọ́n bá ti lo ewé àti egbò tí ó yẹ, yóò kúrò níbẹ̀, àlàáfíà yóò sì wà fún ọmọ náà.

Àìsàn mìíràn tí ó sábà máa ń yọ ọmọdé lẹ́nu ni èyí tí a ń pè ní *'gìrì'* tàbí *'ilẹ̀ tútù'*. Àìsàn yìí tètè máa ń pa ọmọ bí wọn kò bá tètè mójútó o. Oríṣiríṣi ewé, egbó àti àwọn èròjà mìíràn ni wọn yóò fi ṣe àgbo fun irú ọmọ bẹ́ẹ̀, yóò sì máa ta kébé. Èyí tí a ó fi kádìí rẹ̀ nílẹ̀ ni àìsàn eyín. Nígbà tí ọmọ bá ti ń dàgbà tó oṣù mẹta tàbí mẹ́rin ni

wọn yóò ti máa fún un ní àgbo eyín. A kò ní í ṣàìmẹ́nubà á pé oríṣiríṣi àìsàn ni ó máa ń yọjú ní àsìkò tí ọmọ bá fẹ́ hu eyín. Nítorí ìdí èyí, bí àwọn òbí rẹ̀ ti ń ṣe àgbo, bẹ́ẹ̀ ní wọn yóò máa fi ọṣẹ eyín náà wẹ̀ ẹ́ láàárọ̀ àti lálẹ̀.

Ní ìparí, àwọn Yorùbá máa ń tọ́jú àwọn ọmọdé dáadáa kí wọ́n má baà di ọlọ́kùnrùn ọmọ lọ́jọ́ iwájú. Láyé òde òní, ilé-ìwòsàn olóyìnbó ni wọ́n máa ń mú ọmọ lọ. Àmọ́ ṣá o, ọ̀pọ̀ àwọn òbí ni wọ́n máa ń lo àgbo Yorùbá fún ọmọ wọn, pàápàá jùlọ ọmọ tí àrùn ibà bá ń ṣe.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Lẹ́yìn tí a ti ṣe àgbéyẹ̀wò nípa ìtọ́jú oyún títí a fi bí i lọ́mọ, a tún ní bí a ṣe ń tọ́jú ọmọ láti pínníṣín títí yóò fi dàgbà tó bí ọmọ oṣù mẹ́fà. Ní àkókò yìí ni àwọn ọmọ yìí máa ń ṣe àìsàn ọmọdé bí àìsàn jẹ̀díjẹ̀dì, ọ̀kà-orí tàbí joríjorí, gìrì tàbí ilẹ̀ tútù, àìsàn eyín àti àwọn àìsàn ọmọdé mìíràn. Oríṣiríṣi ewé àti egbò ni wọn yóò fi ki àgbo fún àwọn àìsàn wọ̀nyí, bẹ́ẹ̀ ni nígbà mìíràn, wọn yóò ṣe ọṣẹ dúdú tí a ti pa oríṣiríṣi egbò àti ewé pọ̀ mọ́, èyí tí wọn yóò fi máa wẹ̀ ẹ́. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀làjú tí kó òògùn òyìnbó dé lóde òní, a ó rí i pé ọ̀pọ̀ ọmọ Yorùbá ni wọ́n sì tún ń lo àgbo àti ọṣẹ dúdú láti fi ṣe ìtọ́jú àwọn ọmọ wọn.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. *"Àwọn ọ̀nà tí Yorùbá ń gbà tọ́jú ọmọ láyé àtijọ́ kò dára tó"*. Dá sí ọ̀rọ̀ yìí.
2. Àwọn àìsàn ìgbálódé wo ni o rò pé ó ń ṣe ọmọ mọ̀jèsín lódé òní?
3. *"Ìtọ́jú oyún láyé àtijọ́ nípa díde oyún mọ́lẹ̀ léwu púpọ̀"*. Dá sí ọ̀rọ̀ yìí.
4. Ǹjẹ́ o rò pé ó yẹ kí ọmọbìnrin àti ọmọkùnrin máa dá abẹ́?
5. Àwọn àpẹẹrẹ wo ni obìnrin máa ń rí nígbà tí wọ́n bá sẹ̀sẹ̀ fẹ́rakù?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Dáramọ́lá, O. àti Jẹ́jẹ́, A. (2014). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá*, Ìbàdàn, Oníbọn-òjé Press and Book Industries (Nig.). Ltd.

Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*, Ìbàdàn, Gavima Press Ltd.

Ologundudu, D. (2008). *The Craddle of Yorùbá Culture,* U.S., Center for Spoken Words/Institute of Yorùbá Culture.

## MÓDÙ KẸTA: ÀWỌN ÀṢÀ YORÙBÁ KÉÉKÈÈKÉÉ

## ÌPÍN KEJÌ: ÌSỌMỌLÓRÚKỌ ÀTI ÀWỌN ORÚKỌ ỌMỌ

***Àkóónú***

1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ìkómọjáde

4.2 Ìsọmọlórúkọ

4.3 Àwọn oríkì tí a ń sọ ọmọ

44 Orúkọ Àmútọ̀runwá

4.5 Orúkọ ti ó fi Ẹ̀ṣìn, Ipò àti Iṣẹ́ Ìdílé Hàn

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Ní gbogbo àgbáyé ni wọ́n ti máa ń sọ ọmọ lórúkọ, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn àwùjọ mìíràn kì í ṣe ayẹyẹ ìsọmọlórúkọ. Ṣùgbọ́n ní àwùjọ Yorùbá, ó jẹ́ àṣà láti máa ṣe ayẹyẹ ìsọmọlórúkọ tí ó lárinrin, tí ó sì máa ń fẹjú ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà. Ayẹyẹ yìí ni a máa ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ìkómọjáde nítorí ọjọ́ yìí ni a ó gbé ọmọ tuntun náà jáde kúrò, ní ìgbà àkọ́kọ́, ní ìyẹ̀wù tí a ó sì fún gbogbo ènìyàn láti rí àti láti kí i káàbọ̀.

A rí i pé ní ọjọ́ yìí ni a ó fún ọmọ náà lórúkọ tí ó bá yẹ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ọmọ mìíràn ti máa ń mú orúkọ wá láti inú oyún ni, èyí tí Yorùbá gbàgbọ́ pé láti ọ̀run ni wọ́n ti mú orúkọ bẹ́ẹ̀ wá. Àwọn orúkọ mìíràn jẹ́ mọ́ bí a ti bí wọn, nígbà tí àwọn orúkọ mìíràn jẹ́ mọ́ iṣẹ́ tí ìdílé tí a ti bí wọn ń ṣe. Ṣùgbọ́n ṣá o, Yorùbá gbàgbọ́ pé orúkọ ọmọ ni ìjánu ọmọ.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a fẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní ìmọ̀ àti òye lórí:

- Ìtọ́jú tí a máa ń fún ọmọ tuntun láàrín ọ̀sẹ̀ kan tí a bí ọmọ náà sí ayé.
- Pàtàkì ayẹyẹ ìkómọjáde àti ìdí tí Yorùbá ṣe máa ń ṣe ayẹyẹ yìí.
- Mímọ orísìrísì orúkọ tí Yorùbá máa ń fún ọmọ àti ìtumọ̀ àwọn orúkọ wọ̀nyí.
- Àtijẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ mọ̀ nípa àwọn orúkọ àmútọ̀runwá Yorùbá àti ìyípadà tí ó ń dé bá sísọ àwọn orúkọ wọ̀nyí lóde òní.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Kín ni pàtàkì ìkómọjáde àti ìsọmọlórúkọ láàrín àwọn Yorùbá?
2. Kín ni ìtumọ̀ àwọn orúkọ tí a fún ọ ọmọ ní ọjọ́ ti àwọn òbí rẹ sọ ọ́ lórúkọ.
3. Sọ̀rọ̀ lórí àwọn orúkọ àmútọ̀runwá Yorùbá méjì, kí o sì ṣàlàyé irúfẹ́ àwọn ọmọ bẹ́ẹ̀.

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìkómọjáde

Ní ilẹ̀ Yorùbá, ọjọ́ mẹ́sàn-án tí a bá bí ọmọkùnrin ni a máa ní kó o jáde, bẹ́ẹ̀ ni bí ó bá jẹ́ ọmọbìnrin ni, ọjọ́ kẹfà ni wọn yóò ṣe ayẹyẹ ìkójáde rẹ̀. Ṣùgbọ́n bí ó bá jẹ́ ìbejì ni àwọn ọmọ náà, ọjọ́ kẹjọ ni wọn yóò ko ó jáde. Ìkómọjáde yìí ni ọjọ́ tí àwọn òbí ọmọ yìí yóò kọ́kọ́ gbé ọmọ yìí jáde síta láti inú ìyẹ̀wù tí ó ti wà láti ọjọ́ tí wọ́n ti bí i sáyé.

Kí á tó bí ọmọ, pàápàá nígbà tí obìnrin bá ti wà nínú oyún ni bàbá rẹ̀ àgbà yóò ti máa ro irú orúkọ tí wọn yóò sọ ọmọ náà, ìbáà jẹ́ ọkùnrin tàbí obìnrin. Irú orúkọ tí a sábà máa ń sọ irú ọmọ bẹ́ẹ̀ yóò jẹ mọ́ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ kan tí ó ti ṣẹlẹ̀ nínú ìdílé ní àkókò kan sẹ́yìn. Ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá ṣe máa ń sọ pé *"ilé là á wò, kí a tó sọ ọmọ lórúkọ"*.

Ki ó to di ọjọ́ ayẹyẹ ìkómọjáde yìí, àwọn òbí ọmọ náà yóò ti ṣe oríṣiríṣi ìmúrasílẹ̀ de ọjọ́ yìí. Wọn yóò ti pèsè àwọn ohun tí ẹnu ń jẹ, èyí tí wọn yóò fi bọ́ àwọn àgbààgbà àdúgbò tí wọ́n bá wá fún ìkómọjáde náà. Wọn yóò tọ́jú oríṣiríṣi ọtí ìbílẹ̀-ọtikà, àgàdàǹgídí, ògùrọ̀, ẹmu ọ̀pẹ àti àwọn ọtí mìíràn, èyí tí wọn yóò lò fún ìkójáde ọmọ náà.

Ní agbègbè mìíràn, ìyá ọmọ náà gbọ́dọ̀ máa jẹ ọbẹ̀ àtẹ́ bí ọbẹ̀ ìgbá, ẹ̀gúnsí àti ewúro. Lẹ́yìn èyí ni ìyá aròbó náà yóò tó lè máa gbé ọmọ rẹ̀ jáde láti kí ará àdúgbò, tí yóò sì le lọ máa ra ọjà ní ìta tàbí kí ó máa lọ sí ìbòmíràn.

Nínú àwọn ẹbí mìíràn, ìyá ọmọ gbọ́dọ̀ máa sùn lórí àkujá ẹní ni títí yóò fi di ọjọ́ ìkómọjáde yìí. Èyí máa ń wáyé láti tẹ̀lé orò ilé ọkọ tàbí nítorí egún ìdílé kan tí ó ti lè ṣẹlẹ̀ ṣíwájú bóyá wọ́n ti fi ìyà jẹ́ ẹrú tàbí kí wọ́n ti ṣẹ̀ sí àṣẹ òrìṣà kan, èyí tí ó ti fi ìran tàbí ìdílé náà gégùn-ún pé irú ìyà tí ìyàwó kíyàwó tí wọ́n bá fẹ́ wọlé yóò máa jẹ nìyẹn. Lọ́jọ́ ìkómọjáde yìí, ìyá ọmọ yóò wọ aṣọ dáradára, yóò jókòó sí ẹnu ọ̀nà àbáwọlé, yóò sì gbé ọmọ rẹ̀ lé ẹsẹ̀, bẹ́ẹ̀ wọn yóò ṣe àwọn ètùtù kan fún ìkójáde ọmọ náà.

## 4.2 Ìsọmọlórúkọ

Ní kété tí Olódùmarè dá ayé àti àwọn ẹ̀dá alààyè inú rẹ̀ bíi ẹranko inú igbó, ẹyẹ ojú ọ̀run, eku àti àwọn èèrà tó ń rìn nílẹ̀, ni ó dá ẹ̀dá ènìyàn. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ènìyàn ní Olódùmarè pàṣẹ fún láti sọ gbogbo àwọn ẹ̀dá alààyè yòókù ní orúkọ èyí tí wọ́n ń jẹ́ di òní olónìí. Nítorí náà, orúkọ ṣe pàtàkì fún ẹ̀dá alààyè kọ̀ọ̀kan, ìbáà ṣe ènìyàn tàbí ẹranko, bẹ́ẹ̀ ni kò sí ẹ̀dá kan tí kò ní orúkọ tirẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí Dáramọ́lá àti Jẹ́jẹ́ (2014) ṣe sọ, níní orúkọ jẹ́ dandan fún ìdí kan tàbí òmíràn. Ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá fi ya ọjọ́ ìsọmọlórúkọ sọ́tọ̀ tí wọ́n sì ń tẹ̀ lé ètò tí àwọn babańlá wọn fi lélẹ̀.

Ní ọjọ́ ìsọmọlórúkọ yìí, wọ́n yóò gbé orísìírísìí àwọn ohun tí wọ́n yóò fi sọ ọmọ yìí ní orúkọ sílẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, wọn yóò pèsè orógbó, iyọ̀, oyin aádùn, ataare, omi tútú, ẹja, ìrèké àti àwọn nǹkan mìíràn tí wọ́n bá ń lò ní ìdílé náà. Baálé ilé ni yóò máa mú àwọn nǹkan wọ̀nyí, yóò sì máa fi ṣe àdúrà fún ọmọ náà lọ́kọ̀ọ̀kan, yóò máa gé e jẹ, yóò sì máa fi sí ìyá ọmọ náà lẹ́nu láti jẹ ẹ́. Nínú àwọn nǹkan ìwúre fún ọmọ tuntun yìí, bẹ́ẹ̀ ni ọ̀kọ̀ọ̀kan nínú àwọn nǹkan wọ̀nyí ni ó ní ìtumọ̀ wọn.

Bí wọ́n bá fi orógbó wúre fún un, èyí túmọ̀ sí pé ọmọ náà yóò dàgbà, yóò sì dògbó, bẹ́ẹ̀ ni iyọ̀ túmọ̀ sí pé ayé ọmọ náà yóò ní adùn. Oyin àti àádùn ni wọ́n fi ń súre pé ayé ọmọ náà yóò dùn nígbà tí wọ́n yóò fi ataare wúre fún un pé yóò ní ọmọ púpọ̀ láyé. Lẹ́yìn èyí ni bàbá ilé náà yóò fi ọtí ṣe àdúrà pé ọmọ tuntun náà kò ní í díbàjẹ́ láyé nítorí pé ẹni ọtí kì í tí, bẹ́ẹ̀ ni ọtí kì í kan tàbí kí ó tẹ̀. Lẹ́yìn èyí ni wọn yóò mú ètò ìsọmọlórúkọ wá sí ìdánudúró.

## 4.3 Àwọn Oríkì Tí À Ń Sọ Ọmọ

Àṣà Yorùbá nípa pípe ènìyàn lórúkọ ni oríkì rọ̀ mọ́. Ní ọjọ́ tí a bá kó ọmọ tuntun jáde ni a máa ń sọ ọ́ lórúkọ. Ó lè jẹ́ orúkọ àbísọ, ó sì lè jẹ́ àmútọ̀runwá bẹ́ẹ̀ ni a ó sọ ọ́ ní ẹyọ oríkì kan, bẹ́ẹ̀ ni a lè máa fi oríkì yìí pè é gẹ́gẹ́ bí orúkọ.

Àṣà oríkì sísọ ọmọ jẹ́ ọ̀kan pàtàkì tí àwọn Yorùbá ń tẹ̀ lé ní àwùjọ wọn láyé àtijọ́. Ṣùgbọ́n ṣá o, àṣà yìí ti ń rẹ̀yìn láàrín Yorùbá ní òde òní. Oríkì jẹ́ àṣà tí ó gbajúmọ̀ tí ó sì gbilẹ̀ káàkiri ilẹ̀ Yorùbá. Ó jẹ́ ẹ̀ka lítíréṣọ̀ alohùn tí àwọn Yorùbá fi máa ń ki àwọn ọmọ wọn láti mú kí orí wọ́n wú, kí wọ́n sì máa hùwà ọmọlúàbí láàrín àwùjọ.

Ní àwùjọ Yorùbá, bí wọ́n bá ṣe ń sọ ọmọ ní orúkọ, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò máa fún un ní oríkì láti fi HÀN, irú ọmọ tí yóò jẹ́ ní ọjọ́ iwájú. Oríṣiríṣi oríkì ni ó wà-oríkì ẹnìkọ̀ọ̀kan, oríkì àníjẹ́, oríkì àmútọ̀runwá àti oríkì orílẹ̀. Oríkì ẹnìkọ̀ọ̀kan ni oríkì tí a fún ọmọ ní ọjọ́ tí a ń sọ ọ́ ní orúkọ, ìyẹn ní ọjọ́ ìsọmọlórúkọ. Bí wọ́n bá ṣe ń fún ọmọ ní orúkọ tí ó bá àkókò tàbí ìdílé yẹn mu, ni wọn yóò máa fún un ní oríkì tí ó bá ìgbà náà mu.

Oríkì àníjẹ́ ni àwọn oríkì tí ó máa ń fi àbùdá àti ìhùwàsí ọmọ náà hàn bí ó bá ti ń dàgbà sókè títí yóò fi di àgbàlagbà. Ọ́mọ tuntun lè jẹ́ ìbejì, kí ó ní orúkọ àmútọ̀runwá bí i ***Kẹ́yìndé*** pẹ̀lú oríkì tí ó jẹ mọ́ orúkọ àmútọ̀runwá tí ó jẹ mọ́ ọn. Wọ́n lè sọ ọmọ yìí kan náà ní ***Ọládipúpọ̀*** nítorí ó wáyé ní àkókò tí àwọn òbí rẹ̀ ní owó lọ́wọ́. Wọ́n lè sọ ọ́ ní ***Ìṣọ̀lá*** nítorí pé ó wá láti Ìdílé ọba. Wọ́n tún lè fún ọmọ yìí kan náà ní oríkì bí ***Alóńgẹ́*** nítorí ìrísí rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni òun kan náà yìí lè máa jẹ́ ***Ajímátìí*** nítorí pé kì í rìn nínú ìdọ̀tí àti pé ó gbáfẹ́. Òun yìí kan náà sì lè máa jẹ́ ***Balógun*** nítorí oyè tí a fi jẹ nílùú.

Nítorí iṣẹ́ agbẹ́gilére tí ó ń ṣe, wọ́n lè máa pè é ní ***Bàbá Onísọ̀nà***. Nídìí èyí, orúkọ ènìyàn kan ṣoṣo lè máa jẹ́ ***Kẹ́yìndé, Ọládipúpọ̀, Ìṣọ̀lá, Alóńgẹ́, Ajímátìí, Balógun*** àti ***Bàbá Onísọ̀nà.***

Oríkì àmútọ̀runwá ni àwọn oríkì tí ó bá àwọn orúkọ àmútọ̀runwá rìn. Bí àpẹẹrẹ, oríkì Ìbejì, Ìbẹta, oríkì Àjàyí, Àìná, Òjó, Ọ̀kẹ́, Dada, Òdù àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn oríkì yìí ní ó máa ń ní iṣẹ́ tí ó máa ń jẹ́. Òmíràn lè jẹ mọ́ ìtàn àbáláyé, gẹ́gẹ́ bí a ti sọ síwájú, oríkì mìíràn máa ń fi ìwà, ìṣe àti ìrísí ènìyàn tàbí ẹranko hàn.

Oríkì orílẹ̀ náà wà nínú èyí tí a máa ń rí ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ àwọn ìran Yorùbá kọ̀ọ̀kan, ibi tí wọ́n ti wá, ìwà abínibí wọn àti àbùdá ìran kọ̀ọ̀kan. Ó máa ń fi iṣẹ́ àwọn ìran tàbí ìdílé hàn. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ síwájú, bí ẹ̀dá ènìyàn ṣe ní oríkì, bẹ́ẹ̀ ni àwọn ẹranko àti ewéko ìgbẹ́, ní pàápàá jù lọ, gbogbo ẹ̀dá tí Ọlọ́run dá ni ó ní oríkì.

## 4.4 Orúkọ Àmútọ̀runwá

Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, nígbà tí aboyún bá ti ń rọbí ni àwọn àgbà yóò ti máa ṣe àkíyèsí irú ọmọ tí ọmọ náà yóò jẹ́ àti irúfẹ́ orúkọ tí wọn yóò fún un nígbà tí a bá bí i sáyé. Ọ̀nà tí ọmọ yìí gbà wáyé ṣe pàtàkì, yálà ẹsẹ̀ ni ó kọ́kọ́ mú jáde ni tàbí orí. Èyí nìkan kọ́, ìṣesí ọmọ náà lẹ́yìn ìgbà tí ìyá rẹ̀ bí i tán tún gba àkíyèsí.

Bí ọmọ bá ń sọkún púpọ̀ lóru láìṣe pé ọ̀kà-orí ni ó ń ṣe é tàbí tí ọmọ náà kò bá fẹ́ kí wọ́n máa rọ òun ní ìdùbúlẹ̀, ***<u>Òkè</u>*** ni wọ́n máa ń pe irú ọmọ bẹ́ẹ̀. Ọmọ tí a bá bí, tí ó dojú bolẹ̀ ni a máa ń pè ní ***<u>Àjàyí</u>***. Ọmọkùnrin tí a bí, tí ó gbé ibi kọ́rùn ni a ń pè ní ***<u>Òjó</u>***, bẹ́ẹ̀ ni bí ó bá jẹ́ obìnrin ni, ***<u>Àìná</u>*** ni wọn yóò máa pè é. ***<u>Ọ̀ké</u>*** ni ọmọ tí a bí, tí ó fi àwọ̀n bo ara rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni ***<u>Dàda</u>*** ni ọmọ tí ó ní irun orí púpọ̀, ṣùgbọ́n tí irun yìí máa ń lọ̀ mọ́ ara wọn. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, wọn kò gbọdọ̀ gẹ́ irun fún Dàda láìṣe ètùtù tó jẹ mọ́ gígé irun náà. Wọ́n tilẹ̀ gbàgbọ́ pé àwọn Dàda sábá máa ń di ọlọ́rọ̀ nígbà tí wọ́n bá dàgbà. ***<u>Òdù</u>*** ni orúkọ àmútọ̀runwá ọmọ tí a bá bí pẹ̀lú ọmọ ìka ọwọ́ mẹ́fà bẹ́ẹ̀ ni a gbọ́ pé aya Ọ̀rúnmìlà tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ ***<u>Òdù</u>*** ni ó kọ́kọ́ bí irú ọmọ bẹ́ẹ̀, tí irú ọmọ bẹ́ẹ̀ sì ń jẹ́ orúkọ rẹ̀.

***<u>Olúgbódi</u>*** tàbí ***<u>Òhúù</u>*** ni orúkọ àmútọ̀runwá ọmọ tí a bí tí ó ní ìka ẹsẹ̀ mẹ́fà nígbà tí ọmọ tí a bí pẹ̀lú ìdodo rẹ̀ ní líló nígbà tí a bí i ni a máa ń pè ní ***<u>Ìgísánrin</u>***. Yorùbá gbàgbọ́n pé irú ọmọ bẹ́ẹ̀ máa ń jẹ́ ògbójú ọmọ nígbà tí wọ́n bá dàgbà.

Àwọn orúkọ àmútọ̀runwá mìíràn ni àwọn **<u>Ìbejì</u>** (Táíwò àti Kẹ́yìndé), Ìdòwú, Àlàbá, Ìdògbé, **<u>Ẹ̀ta-Òkò</u>** *Ìbẹta, Ìlọ̀rí, Ìgè, Àjàsá, Sàlàkọ́* àti *Tàlàbí, Amúsàn-án* àti *Ato, Òní, Ọ̀la, Ọ̀túnla, Ìreni, Ọmọ́pẹ́, Abíọ́nà, Abíọ́dùn, Abíóyè, Babatúndé,* tàbí *Àbíbá, Babárímìsá, Yétúndé* tàbí *Ìyábọ̀, Jọ́ọ́jọ̀, Awẹ́, Májà, Abíọ́sẹ* tàbí *Bọ́sẹ̀dé, Fìjàbí* àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## 4.5 Orúkọ tí ó fi Ẹ̀sìn, Ipò àti Iṣẹ́ Ìdílé Hàn

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ síwájú, orúkọ àti oríkì sábà máa ń rìn pọ̀, bẹ́ẹ̀ ni àwọn oríkì mìíràn ti di orúkọ pátápátá láti fi ipò ẹni tí ń jẹ́ orúkọ tàbí oríkì bẹ́ẹ̀ hàn. Nígbà mìíràn, oríkì mìíràn tilẹ̀ le ti paradà di bárakú débi pé a ti máa ń gbàgbé orúkọ àbísọ irú ènìyàn bẹ́ẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, a rí ẹni tí ń jẹ́ ***<u>Alówóńlé</u>*** tí ẹnìkankan kò tilẹ̀ mọ orúkọ tí a fi kó o jáde mọ́, bẹ́ẹ̀ ni oríkì oyè bíí ***<u>Balógun</u>*** tí í ṣe oyè tí a fún aṣaájú ogun ní ìgbà kan rí.

A kò gbọdọ̀ gbàgbé pé ẹ̀sìn ìbọ̀rìṣà ní ẹ̀sìn Yorùbá láti àtètèkọ́ṣe. Nítorí náà, àwọn Yorùbá máa ń fún àwọn ọmọ wọn ní orúkọ tí ó jẹ mọ́ òrìṣà tí wọ́n bá ń bọ ní ìdílé wọn nítorí wọ́n gbàgbọ́ pé òrìṣà tí wọn ń bọ ni ó ń fún wọn ní ọmọ.

A ó rí i pé ẹ̀sìn abínibí Yorùbá pọ̀ jańtirẹrẹ, bẹ́ẹ̀ ni àwọn Yorùbá mú ẹ̀sìn wọn ní ọ̀kúnkúndùn nítorí wọ́n gbàgbọ́ pé ó ń ṣe ìrànlọ́wọ́ fún wọn lẹ́lẹ́ka-ǹka ìgbésí ayé wọn – iṣẹ́ ṣíṣe, ètò ìṣèlú, ọrọ̀-ajé, ọmọ-bíbí, ìbágbépọ̀ àlàáfíà, ètò ìlera àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí àpẹẹrẹ, àwọn tí òbí tàbí ìran wọn bá jẹ́ babaláwo máa ń fún àwọn ọmọ wọn ní orúkọ bí Fágbèmí, Fátókí, Fákóredé, Awógbèmí, Awólàjà, Odùlànà, Dòsùnmú, Amósùn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ síwájú, Ògún náà jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn irúnmọlẹ̀ atẹ̀wọ̀nrọ̀ nígbà ìwásẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni àwọn ìdílé Ológùn-ún máa ń sọ ọmọ wọn ní Ògúnbọ̀wálé, Ọ̀gúndípẹ̀, Ògúndélé, Ọ̀gúnṣọlá, Ògúnyẹmí, Ògúndìran, Ògúnlànà, Ògúngbèmí nígbà tí àwọn tí ń bọ òrìṣà Èṣù ń fún ọmọ wọn ní orúkọ bíi Èṣùbíyìí, Èṣùfúnnkẹ́, Èṣùgbayì àti àwọn orúkọ mìíràn tí ó jẹ mọ́ òrìṣà Èṣù. Ní ti àwọn Ọlọ́bàtálá, a máa ń gbọ́ orúkọ bíi Ẹfúnwálé, Ẹfúnjìnmí, Òrìṣàsọnà bẹ́ẹ̀ ni àwọn Oníṣàngó máa ń sọ ọmọ wọn ní Ṣàngódoyin, Ṣàngólàjà, Ṣàngóbùnmi àti Ṣàngódìran. Àwọn Olóró ni wọ́n máa ń jẹ́ orúkọ bíi Oròwálé, Oròjìnmí tàbí Oròyímiká. Níti àwọn àwòrò Ọlọ́ya, wọ́n máa ń sọ orúkọ ọmọ wọn ní Ọyágbèmí, Ọyáṣínà, Ọyákẹ́mi tàbí Ọyáyẹmí. Ní ti àwọn olùsìn Yemọja, a máa ń gbọ́ orúkọ bí i Omíṣadé, Omíṣoore, Omídìjí, Omiyalé àti Omíṣakin.

Yàtọ̀ sí orúkọ tí àwọn Olórìṣà máa ń sọ ọmọ wọn, àwọn orúkọ mìíràn wà tí ó fi ipò tí àwọn òbí ọmọ náà wà hàn nígbà tí wọ́n bí i. Bí àpẹẹrẹ, ọmọ tí wọ́n bí ní àsìkò tí àwọn òbí rẹ̀ wà nínú ọlá àti ọrọ̀ ni wọ́n ń sọ ní *Afọlábí, Ọláìítán, Àjíbọ́lá, Pópóọlá, Ọládipúpọ̀, Ọládiméjì,* tàbí *Ọláńrewájú, Kọ́láwọlẹ́,* bẹ́ẹ̀ ni àwọn ọmọ tí wọ́n bá bí ní ìdílé olóyè tàbí ọba ni wọ́n máa ń fún ní orúkọ bíi Oyèdìran, Oyèbọ̀dé, Oyèyẹmí, Adéoyè, Adékọ́lá, Oyèbọ́lá.

Àwọn orúkọ kan wà tí wọ́n máa ń sọ àwọn ọmọ tí a bí ní àkókò ọdún. Irú wọn ni wọ́n máa ń sọ ní Abọ́dúndé, Abọ́dúnrìn, Abíọ́dún, Ọdúnọlá, Ọdúnladé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Yorùbá gbàgbọ́ pé ọmọ tí ó bá ń kú ní kékeré lemọ́lemọ́ ni wọ́n ń pè ní àbíkú ọmọ. Bí a bá tún ọmọ yìí bí lẹ́ẹ̀kan sí i, wọn yóò sa gbogbo agbára láti máa jẹ́ kí ó kú mọ́. Bí wọ́n ṣe ń lo agbára òògùn bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò máa sọ ọ́ ní orúkọ tí kò gbayì, kí ó má báa lọ mọ́. Irú orúkọ bẹ́ẹ̀ ni Kòsọ́kọ́, Kòkúmọ́, Kíkúmápàyí, Dúróoríkẹ̀ẹ́, Igbókọ̀yí,

Dúrójayé, Ajítòní, Ojúlarí, Bójẹ́sọmọ, Rótìmí, Ọkọ́ya, Làḿbẹ̀, Kúrunmí, Bámitálẹ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Wọ́n máa ń sọ àwọn orúkọ mìíràn láti fi iṣẹ́ ìdílé hàn. Irú wọn ní ìdílé onílù tí wọ́n máa ń sọ ọmọ wọn ní Àyànyẹmí, Aláyàndé, Àyànṣèyí, Àyàndélé àti Àyànwálé. Ní ìdílé ọdẹ, wọn máa ń sọ ọmọ wọn ní Ọdẹ́kúnlé, Ọdẹ́yẹmí, Ọdẹ́gbárò, Ọdẹ́sanmí, Ọdẹ́rìndé, Ọdẹ́bùnmi, Ọdẹ́rímí àti Ọdẹ́lọ́wọ̀.

Wàyí ò, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àyípadà ni ó ti dé bá àṣà ìsọmọlórúkọ yìí ní òde-òní, pàápàá jùlọ nígbà tí ẹ̀sìn òkèèrè méjèèjì tí a gbà ti yí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ní ọkàn padà tí àṣà àti ètò ìsọmọlórúkọ lọ́nà ìbílẹ̀ Yorùbá sì ti ń ròko ìgbàgbé. Nísinsinyìí, orúkọ ẹ̀sìn òkèèrè ni ọ̀pọ̀ àwọn ọmọ Yorùbá ń sọ ọmọ wọn lóde òní. Èyí ni orúkọ bí i Sàámú, Jọ́ọ̀nù, Móósè, Álíìsì, Ẹ́sítà. Yàtọ̀ sí èyí, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọ Yorùbá ni wọ́n ń sọ ọmọ ní orúkọ àwọn Òyìnbó àtọ̀húnrìnwá bíi Nelson, Donald, Johnson, Wilson, ó tilẹ̀ yanilẹ́nu pé ọ̀pọ̀ àwọn ọmọ Yorùbá ni wọ́n ń yí orúkọ bàbá wọn padà láti má ní nǹkan án ṣe pẹ̀lú àṣà abínibí Yorùbá. Èyí ní wọ́n ń fi ọwọ́ òsì júwe ilé bàbá wọn. Irú orúkọ tí wọ́n ń yí padà ni ẹni tí ó ń jẹ́ Òkèwùmí, tí ó sọ ọ́ di Jésùwùmí tàbí ẹni tí ó yí orúkọ ìdílẹ̀ rẹ̀ padà láti Ògúnjìnmí di Olúwajìnmí. Àwọn mìíràn yí tíwọn láti Ògúnkúnlé di Ayọ̀kúnlé, tí àwọn kan sì sọ tiwọn di Jésùgbèmí láti Fágbèmí. Àwọn orúkọ Yorùbá òde-òní kan wà tí wọ́n fi ẹ̀sìn ìgbàlódé hàn. Bí àpẹẹrẹ, Témilolúwa, Jésùpẹ̀lúmi, Olúwapamílẹ́rìn-ìnàyọ̀, Olúwatóósìn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Wàyí ò, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀làjú ẹ̀sìn òkèèrè ti mú kí àwọn kan yí orúkọ ìran àti ìdílé wọn padà sí ti olóyìnbó tàbí sí ti orúkọ mìíràn, ọ̀pọ̀ ni ó sì dúró sinsin lábẹ́ orúkọ abínibí wọn, tí wọ́n sì gbà pé àwọn kò ní àṣẹ láti yí orúkọ abínibí tàbí ti ìran wọn padà nítorí pé Jábésì kò yí orúkọ rẹ̀ padà nínú Bíbélì kí ìgbé-ayé rẹ̀ tó dára. Àwọn ò0pọ̀ ọmọlẹ́yìn Kristi ni wọ́n ń fi orúkọ Yorùbá sọ ọmọ wọn lónìí, èyí tí ó tọ́ka sí i pé ọjọ́ ọ̀la àṣà ìsọmọlórúkọ Yorùbá yóò dára.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín yìí ni a ti sọ̀rọ̀ nípa àṣà ìsọmọlórúkọ àti àwọn orúkọ tí Yorùbá ń sọ ọmọ wọn láye àtijọ́. A wo ìlànà àti ètò ìkómọjáde àti àwọn orò tàbí ètùtù tí wọ́n máa ń ṣe nígbà náà àti bí ó ti ṣe pàtàkì tó nínú ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá.

Èyí nìkan kọ́, a ṣàlàyé nípa ètò ìkómọjáde tí ó jẹ́ ayẹyẹ ìsọmọlórúkọ, kí ètò náà tó bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé láti ìgbà ìwásẹ̀ ni ètò ìsọmọlórúkọ ti bẹ̀rẹ̀ nígbà tí Ẹlẹ́dàá sọ fún Aádámù pé kí ó sọ àwọn ẹ̀dá yòókù ní orúkọ, tí ó sì ṣe bẹ́ẹ̀. Èyí tún fi pàtàkì orúkọ múlẹ̀.

A tún sọ̀rọ̀ lórí oríkì tí í ṣe ẹ̀ka pàtàkì orúkọ, a sì wo orúkọ tí a ń sọ ẹnìkọ̀ọ̀kan bí ó ṣe bá àkókò àti ipò àwọn Yorùbá mu. A ṣàlàyé ìbátan tí ó wà láàrín orúkọ àti oríkì. A wo orúkọ àmútọ̀runwá, èyí tí ó jẹ́ mọ́ ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá àti bí ó ṣe ṣúyọ nínú ẹ̀sìn, ipò ẹ̀dá àti iṣẹ́ ìran Yorùbá. Lẹ́yìn èyí ni a wo ipò tí àṣà yìí wà léréfèé lóde òní.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣàlàyé lẹ́kùu-ún rẹ́rẹ́, pàtàkì orúkọ àti iṣẹ́ tí orúkọ ń jẹ́ láyé ẹ̀dá.
2. Sọ̀rọ̀ nípa ayẹyẹ ìkómọjáde bí ó ṣe máa ń wáyé ní agbègbè rẹ.
3. Ìlànà àti ètò wo ni àṣà ìsọmọlórúkọ máa ń tẹ̀lé ní ìlú rẹ?
4. Sọ̀rọ̀ nípa oríkì orílẹ̀ rẹ, kí o sì sọ àwọn nǹkan tí ó dá lé lórí.
5. Sọ orúkọ Yorùbá márùn-ún tó ṣàfihàn ẹ̀ṣìn Kìrìsítẹ̀ni Ìgbàlóde.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Babayẹmí, S.O. (n.d). *Content Analysis of Oríkì Orílẹ̀.* Ìbàdàn, Institute of African Studies.

Ayọrinde, J.B. (1974). *A Certificate Course on Yorùbá Language*, Ìbàdàn, OUP.

Ogúnbọwálé, P.O. (1983). *Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*, Ìbàdàn, University Press Ltd.

Press and Book Industries (Nig.). Ltd.

Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*, Ìbàdàn, Gavima Press Ltd.

Ologundudu, D. (2008). *The Gaddle of Yorùbá Culture*, U.S., Center for Spoken Words/Institute of Yorùbá Culture.

Ọlájubù, O. (1975). *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*, Ìbàdàn, Longman Nig. Ltd.

Babalọlá, A. (1975). *Àwọn Oríkì Bọ̀rọ̀kìnní*. London, Hodder S. Stoughton Educational.

**MÓDÙ KẸTA**

**ÌPÍN KẸTA: ÀṢÀ ÌRAN-ARA-ẸNILỌ́WỌ́**

***Àkóónú***


1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Àáró

4.2 Àrokodóko

4.3 Ọ̀wẹ̀

44 Àjọ

4.5 Èsúsú (Èésú)

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Àṣà ìran-ara-ẹni-lọ́wọ́ ṣe pàtàkì láàrín àwọn Yorùbá ní ayé àtijọ́. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ọ̀nà ìran-ara-ẹni lọ́wọ́ yìí ti ń kásẹ̀ nílẹ̀ ní àwọn agbègbè kan, pàápàá ní àwọn ìlú àti ìletò ńláńlá, àwọn ọ̀nà kán sì wà tí ó ń tẹ̀síwájú lónìí.

A ṣe àlàyé irú àwọn àǹfààní tí ó wà nínú a ń ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ara ẹni nípa fifi ọwọ́ so ọwọ́ pọ̀ láti mú iṣẹ́ ya tàbí láti bo ara wa ní àṣírí kan tàbí òmìràn. A wòye pé igi kan kò lè dá igbó ṣe rárá àti pé àgbájọ ọwọ́ ni a fi ń sọ àyà. Nítorí náà, bí iṣẹ́ ara ẹni bá pọ̀ ní àpọ̀jù, nígbà mìíràn, a máa ń ké sí ọ̀rẹ́, ẹbí àti aládùúgbò láti nawọ́ ìrànlọ́wọ́, kí nǹkan lè dẹrùn.

Nígbà mìíràn, a le pè fún ìrànlọ́wọ́ fún ilé kíkọ, oko ṣíṣán tàbí ríro, àti fún kíkore irè oko tàbí nǹkan mìíràn. A lè bèèrè fún ìràn-lọ́wọ́ owó lọ́dọ̀ ẹgbẹ́ tàbí kí àwùjọ pe àwọn ènìyàn ìlú tàbí ìletò fún àtiyẹnà, àtigbẹ́dò fún àǹfààní ìlú lápapọ̀. Lára àwọn ọ̀nà yìí ni a máa ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ọ̀wẹ̀, ààró, àjọ, èsúsú, àrokodóko, àgbá-ẹ̀bọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ṣùgbọ́n ṣá o, díẹ̀ nínú àwọn àṣà yìí sì ń tẹ̀síwájú pẹ̀lú ọ̀làjú òde òní. Àlàyé wọ̀nyí ni a ṣe nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí láti tẹ̀síwájú nínú ìmọ̀ àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Èròǹgbà àti àfojúsùn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni:

- Láti mú kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìmọ̀ nípa pàtàkì ìran-ara-ẹni-lọ́wọ́ ní àwùjọ wa lóde òní.
- Kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí lè mọ ipò tí àṣà yìí wà lóde òní.
- Láti lè mú kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ronú, kí wọ́n sì tọ́ka sí àtúnṣe tí ó bá yẹ àti àwọn ọ̀nà mìíràn tí a lè gbà tẹ̀síwájú nínú àṣà ìgbáyéró yìí.
- Kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè máa fínnúfíndọ̀ ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ọmọnìkejì wọn lọ́nà tí ó tọ́.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Dárúkọ ọ̀nà márùn-ún tí àwọn Yorùbá máa ń gbà ran ara wọn lọ́wọ́ láyé àtijọ́.
2. Irú iṣẹ́ ìran-ara-ẹni-lọ́wọ́ wo ni wọ́n ń ṣe ní agbègbè tàbí ìlú rẹ lónìí?

3. Sọ nípa iṣẹ́ ìran-ara-ẹni-lọ́wọ́ tí o ti kópa rí ní agbègbè rẹ àti irú ipa tí o kó.

4. Ì̀yàtọ̀ wo ló wà nínú ààró àti ọ̀wẹ̀?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ààró

A lè sọ pé ìtumọ̀ ààró ni ihun tí a bá ara ẹni ro tàbí àbáro. A sì lè sọ pé ohun tí ó túmọ̀ sí ní *"bá mi ro tèmi, kí èmi náà bá ọ ro tìrẹ"*. Ní pàtó, ààró jẹ mọ́ iṣẹ́ ìrànlọ́wọ́ tí ẹni méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ máa ń ṣe nínú oko ara wọn.

Orí ọ̀rẹ́ ni àwọn Yorùbá gbé àṣà yìí lé, ó sì dúró lórí ìfẹ́ pẹ̀lú. Àjọṣepọ̀ máa ń fa oríire báni bí àìfọwọ́sowọ́pọ̀ ṣe lè fa orí burúkú. Èyí ni pé bí ìrẹ́pọ̀ àti ìfọwọ́sowọ́pọ̀ bá wà láàrín àwùjọ, ìlọsíwájú yóò wà, bẹ́ẹ̀ ni iṣẹ́ àti gbogbo nǹkan dáadáa yòókù yóò máa lọ déedée. Nítorí náà, ìbáà ṣe ọkọ àti aya tàbí mọ̀lẹ́bí ní abúlé, ìletò tàbí ìlú ńlá, pàápàá kí o ṣe orílẹ̀-èdè, ìran-ara-ẹni-lọ́wọ́ àti àjùmọ̀ṣepọ̀ ṣe pàtàkì láti mú àlàáfíà wá.

Ara àṣà ìfọwọ́sowọ́pọ̀ yìí ni ààró, èyí tí ó túmọ̀ sí "ṣe fún mi, kí n ṣe fún ọ" gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ síwájú, nítorí àjéjé ọwọ́ kan kò gbẹ́rù dórí àti pé àgbájọ ọwọ́ ni a fi ń sọ̀yà. Ààró wúlò púpọ̀ láàrin àwọn àgbẹ̀ láyé ọjọ́un, ṣùgbọ́n kò ní pé a ó se oúnjẹ rárá nítorí pé wọn kì í fi dandan le oúnjẹ pípèsè. Kò sí ààyè fún ìmẹ́lẹ́ tàbí ìrégbè nítorí ẹ̀mí ìfẹ́ ni wọ́n fi máa ń bá ara wọn ṣiṣẹ́, bẹ́ẹ̀ ni àwọn tí ó bá jẹ́ irọ̀ kan náà tàbí tí wọ́n jẹ́ ọ̀rẹ́ ni wọ́n sábà máa ń ṣe ààró pọ̀. Alágbára kì í bá ọ̀lẹ ṣe ààró pọ̀, bẹ́ẹ̀ ni àwọn tí agbára wọn bá fẹ́rẹ̀ dọ́gba ni wọ́n máa ń gbà láti bá ara wọn ṣe ààró pọ̀. Wọn kì í fi ààró kọ́ iṣẹ́ oko ríro nítorí pé ẹni tí ó bá mọ iṣẹ́ àgbẹ̀ í ṣe dáadáa ni ó máa ń kẹ́gbẹ́ ààró.

Bí wọ́n bá lọ sí oko ẹnikan lónìí, wọn yóò lọ sí oko ẹnìkejì lọ́la títí wọn yóò fi ṣíṣẹ kárí oko ẹlẹ́gbẹ́ wọn. Ṣùgbọ́n ṣá, àdéhùn ti wà, iye ebe tí wọn yóò kọ tàbí ṣán nínú oko ẹnìkọ̀ọ̀kan. Òjò ń rọ̀ tàbí pé oòrùn ń ràn kò gbọdọ̀ dá iṣẹ́ dúró bẹ́ẹ̀ ni iye oko tí àwọn aláààró yóò ṣe gbọ́dọ̀ pé ṣánṣán kí wọ́n tó ṣíwọ́ iṣẹ́.

Kò sí iṣẹ́ tí a kò lè fi ṣe ààró, ó lè jẹ́ oko ríro, ebè kíkọ, ilẹ̀ pípa ilé kíkọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, bẹ́ẹ̀ ni oníkálukú ọmọ ẹgbẹ́ ààró ni yóò ti jẹun wá láti ilé rẹ̀, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹni tí wọ́n lọ síṣẹ́ lóko rẹ lè pèsè oúnjẹ fún wọn nígbà mìíràn ṣùgbọ́n èyí kì í ṣe dandan.

Àǹfààní tí ó wà nínú ààró ṣíṣe pọ̀ díẹ̀. Lọ́nà kìn-ín-ní, iṣẹ́ a máa rìn dáadáa níbi tí àwọn méjì tàbí mẹ́ta bá gbé ń ṣiṣẹ́ kan-náà pọ̀. Wọn yóò máa gbọ́ ohun ara wọn, wọ́n sì lè máa dá orin amúṣẹ́yá èyí tí yóò fún wọn ni okun àti agbára sí i. Ẹni tí ó bá ń ṣiṣẹ́ ààró yóò máa ní agbára iṣẹ́ sí i, àìsàn kò sì ní í le fi àgọ́ ara rẹ̀ ṣe ilé. Àǹfààní mìíràn ní pé nípa fífi ààró ṣiṣẹ́ lóko kì í jẹ́ kí iṣẹ́ gba àkókò púpọ̀ jù.

## 4.2 Àrokodóko

Ọ̀nà kúkúrú mìíràn tí ọ̀rẹ́ méjì lè gbà bá ara wọn ṣe iṣẹ́ oko ni a ń pè ní àrokodóko. Ọ̀rẹ́ kò gba ẹlẹ̀ta, elèjì ni ọ̀rẹ́ gbà ni ọ̀rọ̀ àrokodóko jẹ́ nítorí pé ènìyàn méjì ló máa ń kópa nínú iṣẹ́ yìí. Eléyìí kì í ná wọn lówó, bẹ́ẹ̀ ni kì í sábà ná wọn ni oúnjẹ nítorí pé nǹkan tí wọ́n bá rí ni wọn yóò fi panu nínú oko lẹ́yìn tí wọ́n bá ti jẹun ààrọ̀ ní ilé kóówá wọn. A ó rí i pé Ìfẹ́ ni okùnfà èyí nítorí pé láìsí ìfẹ́, ọ̀rẹ́ kò sí, bẹ́ẹ̀ ni láìsí ìfẹ́, kò le sí àjọṣepọ̀ láàrín ènìyàn méjì.

Àwọn àgbẹ̀ méjì yóò ṣètò àti àdéhùn láti máa ro oko lóko ara wọn ní ọjọ́ kan náà. Bí wọ́n bá ṣiṣẹ́ lóko ẹnìkan láààrọ̀, wọn yóò lọ ṣiṣẹ́ lóko ẹnìkejì lọ́sàn-án. Irú iṣẹ́ yìí máa ń mú iṣẹ́ yá.

Bí a bá wo àléébù tí ó wà nínú iṣẹ́ àrokodóko, nígbà mìíràn ààrẹ̀ yóò ti dé sí ọ̀rẹ́ méjèèjì kí wọ́n tó kúrò ní inú oko ẹnìkan láààrọ̀, kí wọ́n tó lọ bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ nínú oko ẹnìkejì ní ọ̀sán. Ìyẹn ni pé ó máa ń pé ẹni tí wọ́n ṣiṣẹ́ nínú oko rẹ̀ ní òwúrọ̀ ju ẹni tí wọ́n lọ ṣiṣẹ́ nínú oko rẹ̀ lọ́sàn-án. Bóyá ohun tí ó fà á tí àṣà àrokodóko yìí fi ń káṣẹ̀ nílẹ̀ nìyí, ṣùgbọ́n ó ṣe pàtàkì kí á mọ̀ pé àṣà yìí máa ń mú iṣẹ́ yá àti pé lórí ìfẹ́ ni a ti gbé e kalẹ̀.

## 4.3 Ọ̀wẹ̀

Ọ̀wẹ̀ jẹ́ Ìrànlọ́wọ́ iṣẹ́ tí ọ̀pọ̀ ènìyàn máa ń ṣe fún ẹni tí ó bá bẹ ọ̀wẹ̀. Ó jẹ́ ọ̀kan nínú àṣà ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti ìran-ara-ẹni-lọ́wọ́ láàrín àwọn Yorùbá láyé àtijọ́. Lóòótọ́ ni ọ̀wẹ̀ náà máa ń jẹ́ "ṣe-fún-mi-n-ṣe-fún-ọ", ṣùgbọ́n kì í ṣe ní wàrà-ǹ-ṣeeṣa bí i ti ààró tàbí àrokodóko. Ọ̀wẹ̀ máa ń ní oúnjẹ rẹpẹtẹ nínú, bẹ́ẹ̀ ni ènìyàn sábà máa ń pọ̀ níbi ọ̀wẹ̀ ju ààró lọ.

A le bẹ ọ̀wẹ̀ kọ́ ilé, a lè bẹ ọ̀wẹ̀ ká kòkó tàbí kí á bẹ ọ̀wẹ̀ sán oko. Ṣùgbọ́n ṣá o, ìwà rere ṣe pàtàkì fún ẹni tí yóò bá bẹ àwọn ènìyàn lọ́wẹ̀. Irú ènìyàn bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́

ọmọlúàbí, ọlọ́yàyà, kí ó sì jẹ́ ẹni tí òun náà kì í gbẹ́yìn níbi ọ̀wẹ̀ jíjẹ́. Ẹni tí yóò bẹ ọ̀wẹ̀ náà gbọ́dọ̀ jẹ́ alágbára nítorí pé Yorùbá kì í bẹ ọ̀lẹ àti olè lọ́wẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni wọn kì í jẹ́ ọ̀wẹ̀ fún irú ẹni bẹ́ẹ̀ pẹ̀lú.

Ara ọ̀wẹ́ ni kí àwọn ọdẹ bẹ ẹgbẹ́ wọn láti bá wọn pa ẹran ìgbẹ́, yálà fún ọdún ọba, tàbí kí ẹnìkan nínú wọn fẹ́ ṣe nǹkankan. Òhun tí a ní láti kíyèsí ni pé ẹni tí ó bá bẹ ọ̀wẹ̀ ẹran ìgbẹ́ pípa ni ó gbọdọ̀ ra ẹ̀tù, àhàyá, ìṣáná, àti àwọn èlò ìbọn yíyìn mìíràn tí wọn yóò lò ní ìgbẹ́ ọdẹ. Oríṣi ìgbẹ́ ọdẹ mìíràn ni ìgbẹ́ **ajùmọ̀dẹ** tàbí **wawàá**. Èyí ni ìgbẹ́ ọdẹ àjùmọdẹ papọ̀ nínú èyí tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdẹ akọni àti àwọn ọmọ ọdẹ yóò kórajọ pọ̀ láti dẹ igbó ńlá nínú èyí tí àwọn ẹranko abàmì wà. Àwọn ọdẹ akọni yóò dè yíká igbó bẹ́ẹ̀ pẹ̀lú ìbọn wọn lọ́wọ́ nígbà tí àwọn ọdẹ àti àwọn ọmọ ọdẹ yòókù yóò máa rúgbó sí wọn títí tí àwọn ẹranko náà yóò fi máa yọjú sí àwọn akọni ọdẹ tí wọ́n lúgọ dè wọ́n. Eléyìí jẹ́ ìfọwọ́sowọpọ̀ láti rí ẹran pa kí wọ́n sì pín in láàrin ara wọn.

A le bẹ ọ̀wẹ̀ láti fi ṣe iṣẹ́ ara ẹni bẹ́ẹ̀ ni a lè bẹ ọ̀wẹ̀ láti fi ṣe iṣẹ́ fún àna ẹni. Láyé àtijọ́, ọ̀wẹ̀ láti fi ṣe iṣẹ́ fún àna ẹni ni ó wọ́pọ̀ jùlọ. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé ó di dandan kí ẹni tí ó fẹ́ ọmọbìnrin sọ́nà máa jẹ́ ọ̀wẹ̀ fún baba ìyàwó àfẹ́sọ́nà rẹ̀ nígbàkúùgbà tí àna rẹ̀ bá ké sí i láti ṣe bẹ́ẹ̀. Ọ̀wẹ̀ ilé àna yìí ṣe pàtàkì púpọ̀ nítorí pé bí ọkùnrin kò bá jẹ́ ìpè àna yìí, àna rẹ̀ lè gba ọmọ rẹ̀ padà lọ́wọ́ rẹ̀.

Wọ́n máa ń dájọ́ sí ọ̀wẹ̀ bíbẹ̀ ni. Ó lè jẹ́ ọ̀sẹ̀ méjì, ó lè jẹ́ ọjọ́ mẹ́tàlá, ó sì lè jẹ́ ọjọ́ mẹ́tàdínlógún. Tẹbí tọ̀rẹ́ ni a máa ń dá ọjọ́ ọ̀wẹ̀ yìí fún bẹ́ẹ̀ ni tọmọdé tàgbà ni ó má ń jẹ́ ọ̀wẹ̀. Bí ọjọ́ ọ̀wẹ̀ bá ti ń súnmọ́, bẹ́ẹ̀ ni ẹni tí ó bẹ ọ̀wẹ̀ náà yóò máa rán àwọn ènìyàn létí títí ọjọ́ yóò fi pé.

Kí ènìyàn tó bẹ ọ̀wẹ̀ ni yóò ti mọ bí iṣẹ́ náà ti pọ̀ tó àti iye ènìyàn tí òun yóò bẹ̀ lọ́wẹ̀ yóò ti pọ̀ tó, nítorí ẹni tí wọ́n ń bẹ ọ̀wẹ̀ lọ sí oko rẹ̀ gbọdọ̀ múra láti pèsè ohun jíjẹ àti mímu tí ó pọ̀, èyí tí àwọn tí a bẹ̀ lọ́wẹ̀ yóò jẹ ní àjẹyó àti àjẹṣẹ́kù. Bí oúnjẹ tí a pèsè fún àwọn tí a bẹ̀ lọ́wẹ̀ kò bá bójúmu tó, tí kò jọjú, wọ́n yóò kúrò níbẹ̀ láìdunnú sí irú nǹkan bẹ́ẹ̀, wọn yóò sì bu ẹnu àtẹ́ lu ẹni tí ó bẹ ọ̀wẹ̀ náà àti pé wọn kò ní í jẹ́ ọ̀wẹ̀ fún irú ẹni bẹ́ẹ̀ mọ́ lọ́jọ́ iwájú.

Yàtọ̀ sí iṣẹ́ oko, oríṣi iṣẹ́ mìíràn tí wọ́n tún máa ń fi ọ̀wẹ̀ ṣe ni ilé kíkọ́, bẹ́ẹ̀ ni ènìyàn lè kọ odidi ilé pẹ̀lú ọ̀wẹ̀, ṣùgbọ́n wọ́n máa ń pèsè jíjẹ àti mímu fún àwọn òsìṣẹ́ náà.

Láyé àtijọ́, àwọn ìlú máa ń bẹ ọ̀wẹ̀ láti yẹ ọ̀nà, bẹ́ẹ̀ ni ọ̀wẹ̀ yìí jẹ́ ọ̀ràn-anyàn fún ẹnikọ̀ọ̀kan láti lọ síbẹ̀. Wọ́n máa ń jẹ ẹni tí kò bá lọ síbi ọ̀wẹ̀ ìlú níyà. Èyí yàtọ̀ sí ọ̀wẹ̀ ẹnìkọ̀ọ̀kan tí kò pa dandan, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ohun tí ènìyàn bá ṣe ní yóò gbà. Ṣùgbọ́n sá o, àwọn ènìyàn kì í sábà kọ ìpè sí ọ̀wẹ̀ láyé àtijọ́ nítorí pé wọ́n mọ̀ pé mọ̀kànmọ̀kàn ni oyèé kàn. Ẹni tí a bẹ̀ lọ́wẹ̀ tí ó kọ̀, ọjọ́ tirẹ̀ náà yóò dé. Èyí jásí pé ní ọjọ́ tí ó bá kan òun náà, ó lè má rí ènìyàn dá a lóhùn nítorí pé adìẹ ìrànà, kì í ṣe ohun àjẹgbé.

## 4.4 Àjọ

Àjọ ni a lè túmọ̀ sí *Owó Àdájọ*, èyí ni owó tí à ń dá títí yóò fi kóríjọ, kí á tó kó o. Àwọn mìíràn tilẹ̀ máa ń rò pé nǹkan kan náà ni àjọ àti èsúsú ni. Èyí kò rí bẹ́ẹ̀, nítorí pé wọ́n yàtọ̀ sí ara wọn, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n jọra díẹ̀. Ṣùgbọ́n sá o, ó lè má ṣe e ṣe láti ya àjọ àti èsúsú sọ́tọ̀ bí a bá fẹ́ sọ̀rọ̀ wọn, nítorí dídá ni wọ́n máa ń dá àjọ àti èsúsú, bẹ́ẹ̀ ní àwọn méjèèjì ni wọ́n máa ń dá owó pamọ́ títí di àkókò tí yóò kórí jọ tí wọn yóò sì kó o tàbí gbà á.

Àjọ ojoojúmọ́ wà, bẹ́ẹ̀ ni àjọ ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ wà pẹ̀lú. Ọ̀nà yìí jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ọ̀nà tí àwọn Yorùbá máa ń gbà ran ara wọn lọ́wọ́. Nípa báyìí, wọ́n yóò kó ara wọn jọ, wọn yóò fi ẹnìkan ṣe olórí, wọn yóò máa fi owó pamọ́ díẹ̀díẹ̀ títí yóò fi di àkókò tí yóò kóríjọ, tí wọn yóò sì gbà á láti fi gbọ́ bùkáátà tí wọ́n bá fẹ́. A ó rí i pé àjọ dídá si tún wà lóde òní.

Àwọn kan ni yóò jókòó láti dábàá fún bíbẹ̀rẹ̀ àjọ, bẹ́ẹ̀ ni bí ẹnikejì bá ti fi ara mọ́ ọn, tí wọ́n tún rí ẹnìkẹta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ, wọn yóò jókòó láti ṣètò iye tí wọn yóò máa dá àti bí wọn yóò ṣe máa kó o. Iye kannáà ni oníkálukú yóò máa dá, ṣùgbọ́n ẹlòmíràn tí ó bá le máa dá ọwọ́ tàbí ọ̀nà méjì yóò fi orúkọ sí ọ̀nà méjì. Ṣùgbọ́n bí ó bá kọ́kọ́ kó ọ̀kan, àkókẹ́yìn ni èkejì sábà máa ń jẹ́. Nígbà mìíràn, ẹlòmíràn máa ń dá ọwọ́ mẹta, ṣùgbọ́n ohun tí ó ṣe pàtàkì ni pé adéhùn máa ń wà nípa dídá àti kíkó rẹ̀.

Àwọn kan máa ń dá àjọ ní ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ tàbí ní ọrọ̀ọrún, bí ó bà sì ṣe àwọn oníṣòwò tàbí àwọn oníwóróbo ni, ojoojúmọ́ ni wọ́n máa ń dá tiwọn, bẹ́ẹ̀ ni àwọn oníṣẹ́ oṣù máa ń dá tiwọn ní ìparí oṣooṣù.

Nígbà mìíràn, bí àjọ kò bá tí ì kan ẹnìkan, ṣùgbọ́n tí ìṣòro ìnáwó tàbí bùkáátá kan bá dé bá a, wọ́n lè bẹ ẹni tí àjọ bá kàn kí ó yọ̀nda fún ẹni tí ìṣòro ìnáwó dé bá náà

tàbí kí wọ́n jọ pín in sí méjì. Kí wọ́n sì tún jọ pín ti ẹnìkejì náà nígbà tí ó bá kàn án. Èyí ni pé *"gbà mí lójọ̀, kí n gbà ọ́ lẹ́ẹ̀rùn"*. Nídàkjejì ẹ̀wẹ̀, bí ẹnìkan bá kó àjọ, ẹlòmìíràn tí ó ní ìṣòro owó le lọ bá a ní bòńkẹ́lẹ́ láti ya díẹ̀ lọ́wọ́ rẹ̀ fún àṣírí bíbò, bẹ́ẹ̀ ni eléyìí jẹ́ ìrànlọ́wọ́ bákan náà.

Ó ṣe pàtàkì láti ṣe àkíyèsí pé ọ̀rẹ́ pẹ̀lú ìfẹ́ àti ìgbẹ́kẹ̀lé nínú ara ẹni ni ó máa ń pilẹ̀ àjọ, bẹ́ẹ̀ ni ẹni tí wọ́n bá rí i pé ó jẹ́ oníwà rere, tí kì í ṣe alábùkù tàbí aláìṣòótọ́ ènìyàn ni wọ́n sábà máa ń bá dá àjọ pọ̀. Ìdí ni pé wọn kò ní í fẹ́ ẹni tí yóò kú sọ́nà lẹ́yìn tí ó bá ti gba àjọ tán, tàbí bí kò tilẹ̀ tíì gbà, nípa báyìí, tí àjọ yóò wá ní akùdé.

Nípasẹ̀ àjọ dídá ni a ti rí i pé àwọn Yorùbá náà máa ń kọ àkọsílẹ̀ nígbà àtijọ́. Bí wọ́n bá ti dá àjọ kan, wọn yóò mú èédú, wọn yóò fi kọ àkọsílẹ̀ rẹ̀ sẹ́yìn ìlẹ̀kùn abógundé wọn tàbí ibi kan tí wọ́n ti bọ́ tàbí fi ìpalé pa. Bí àríyànjiyàn kan bá fẹ́ wáyé, wọn yóò lọ wo àkọsílẹ̀ wọn. A tún ní láti kíyèsí i pé àkọsílẹ̀ àwọn baba wa láyé àtijọ́ máa ń ní *'kọmá'* nígbà mìíràn àti pé ẹlòmíràn le máa mọ ìtumọ̀ rẹ̀ àyàfi ẹni tí ó kọ àkọsílẹ̀ náà.

## 4.5 Èsúsú

Èsúsú súnmọ́ àjọ pẹ́kípẹ́kí ṣùgbọ́n oko kì í jẹ́ ti baba tọmọ kí ó má ní ààlà. A le fi àṣà èsúsú wé ẹgbẹ́ alájẹ̀ṣẹ́kù tí a ń ṣe lóde òní. A kì í kó èsúsú bí wọ́n ṣe máa ń kó àjọ, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ilé ìṣura tí wọ́n fi máa ń ran àwọn tí wọ́n bá ní ìṣòro lọ́wọ́.

Èsúsú ni owó tí a fi pamọ́, tí a jẹ́ kí ó kóríjọ kí ọmọ ẹgbẹ́ elésùsú tó kó o. Wọn yóò ti ṣètò àwọn ènìyàn tí yóò máa dáa àti ìgbà tí wọn yóò máa dá a tẹ́lẹ̀. Èsúsú dídá le jẹ́ oṣooṣù, ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ tàbí ọrọọrún. Lẹ́yìn tí wọ́n bá ti ṣètò yìí tán ni wọn yóò yan olórí láàrín wọn. Olórí yìí ni yóò máa ṣe àkóso fún ẹgbẹ́ eléèésú bẹ́ẹ̀ ni òun ni yóò máa ṣe akápò wọn. Lẹ́yìn ìgbà tí wọ́n bá ti kéde rẹ̀ tán láàrin ọ̀rẹ́, ẹbí àti ojúlùmọ̀, wọn yóò dá ọjọ́ tí yóò bẹ̀rẹ̀.

Òfin wà fún èsúsú, bẹ́ẹ̀ ní ó ní ètò tirẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àjọ. Iye àwọn tí ó bá bẹ̀rẹ̀ rẹ̀ ni yóò parí rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni iye owó kan náà ni ọmọ ẹgbẹ́ elésùsú gbọ́dọ̀ máa dá. Olórí eléèèésú tàbí olórí àjọ máa ń gba *'owó-ìkó'* fún iṣẹ́ àkóso àti ìpamọ́ owó tí ń ṣe. Gẹ́gẹ́ bí ètò èsúsú, ẹnikọ̀ọ̀kan ni ó máa ń kó gbogbo owó tí wọ́n bá dá nínú ìpàdé kọ̀ọ̀kan. Bí ènìyàn kan bá ti kó èsúsú tirẹ̀, ó ní láti bá wọn dá èsúsú parí, bẹ́ẹ̀ ni olórí èsúsú ni ó

máa ń ṣe ètò kíkó rẹ̀. Ṣùgbọ́n sá o, ètò yìí lè yí padà nígbà mìíràn bí a bá rí ẹni tí bùkáátà tàbí ìnáwó bá kàn lójijì, tí ó sì lọ bá olórí èsúsú láti bẹ̀ ẹ́ pé kí ó jẹ́ kí òun kó èsúsú ti òun dípò ẹni tí ó kàn. Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, èyí lè má ṣe é ṣe.

A kò ní í saìrántí pé bí wọ́n ṣe ń yá ọmọ ẹgbẹ́ lówó náà ni wọ́n máa ń yá ará ìta tí kì í ṣe ọmọ ẹgbẹ́. Ẹnikẹ́ni tí ó bá ń fẹ́ ìrànlọ́wọ́ owó, yálà ọmọ ẹgbẹ́ tàbí ará ìta ni wọ́n lè fún ní iye tí ó bá bèèrè fún, ṣùgbọ́n tí yóò máa san èlé lórí iye tí ó bá yá náà títí yóò fi san án padà tán. Irú owó báyìí sábà máa ń di gbèsè ìdílé bí wọn kò bá tètè dá a padà, tí èlé rẹ̀ sì ń pọ̀ sí i. A ní láti kíyèsí i pé ọmọ ẹgbẹ́ ni ó kọ́kọ́ máa ń rí owó gbà, kí ará ìta tó rí. Wàyí ò, a kò ní í saìmẹ́nubà á pé bí èpè ni irú owó èlé báyìí, pàápàá èyí tí wọn kò bá tètè dá padà máa ń jẹ́ nítorí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ni wọ́n máa ń yá irú bẹ́ẹ̀ kò sí ní í le san án padà pẹ̀lú ìrọ̀rùn bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìrànlọ́wọ́ pàtàkì ni wọ́n fi ṣe fún irú ẹni bẹ́ẹ̀.

Ṣùgbọ́n, ju gbogbo rẹ̀ lọ, lórí ọ̀rẹ́ tàbí ilẹ̀-ọ̀rẹ́ ni àwọn nǹkan wọ̀nyí ń dá lé. Wọ́n gbàgbọ́ pé ìwà lẹwà àti pé ìwà ni a fi ń mọ irú ẹni tí ènìyàn jẹ́, bóyá ènìyàn rere tàbí búburú àti pé ẹni tí wọn yóò bá bá da nǹkan pọ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ ọmọlúàbí ènìyàn. Wàyí ò, ìdálùú nìṣèlú, eégún ní í gbowó òde Òṣogbo, òrìṣà ní í gba t'Ifẹ̀.

Ní ìparí, a lè tọ́ka sí àwọn ọ̀nà mìíràn tí Yorùbá máa ń gbà ran ara wọn lọ́wọ́ láyé ọjọ́un nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ mìíràn lọ́jọ́ iwájú. Lára wọn ni Asingbà tàbí Àgbá-ẹ̀bọ̀, Ẹgbẹ́ dídá, Ọrẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Síwájú sí i, a ó ṣàkíyèsí pé bí ọ̀làjú ti ṣe àkóbá fún àwọn ẹ̀ka àṣà yìí tó, àwọn Yorùbá sì tún ń ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ara wọn lóde-òní nípa àjọ, èsúṣú tí a mọ̀ sí ẹgbẹ́ aláfọwọ́sowọ́pọ̀ lónìí.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Àṣà ìran-ara-ẹni-lọ́wọ́ láàrín àwọn Yorùbá ni a ṣe àlàyé nínú ìpín yìí. Ó jẹ́ àṣà tí ń mú àlàáfíà bá àwùjọ, tí ó sì ń jẹ́ kí ìdàgbàsókè wà fún ìlú àti ìletò.

Oríṣiríṣi ọ̀nà ni àwọn Yorùbá máa ń gbà ran ara wọn lọ́wọ́ lọ́jọ́ ọjọ́un. Èyí bẹ̀rẹ̀ láti ibi àáró dídá, ọ̀wẹ̀ bíbẹ̀, ìlànà àrokodóko, àjọ àti èsúsú dídá, tí o fi mọ́ àsìngbà àti ẹgbẹ́ dídá. Àwọn àṣà yìí ni ọ̀làjú ti fà sẹ́yìn, tí ìyípadà sì ti dé bá lóde òní.

Àáró kò wọ́pọ̀ mọ́, pàápàá ní àwọn ìlú ńláńlá. Ní àwọn ìletò àti abúlé náà ni a kò tilẹ̀ gbúròó ohun tí ń jẹ́ àrokodóko mọ́. Àwọn ìlú kékeré kò sin àsìngbà mọ́ fún ìlú ńláńlá mọ́. Wàyí ò, àjọ dídá àti èsúsú sì ń lọ síwájú láàrín àwùjọ Yorùbá, pàápàá jù lọ,

bí a ba wo ipa tí àwọn ẹgbẹ́ alájẹ̀ṣẹ́kù ń kó lóde òní. Bí a bá ṣe àkíyèsí dáadáa, àwọn Ẹgbẹ́ ọmọ Ìlú tílẹ̀ tún ti ń kó ara jọ pọ fún ìrànlọ́wọ́ ẹnìkọ̀ọ̀kan àti ìlú lápapọ̀.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣàlàyé àwọn ọ̀nà tí Yorùbá ń gbà ran ara wọn lọ́wọ́ láyé àtijọ́.
2. Ǹ jẹ́ o rò pé àwọn ọ̀nà yìí ń tẹ̀síwájú lóde òní?
3. Ìyàtọ̀ àti ìjọra wo ló wà láàrín Ààró àti Ọ̀wẹ̀?
4. Àwọn ọ̀nà wo ni àwọn ènìyàn ìlú ń gbà ran ara wọn lọ́wọ́ lóde òní?
5. Báwo ni wọ́n ṣe ń ṣe àgbá-ẹ̀bọ̀ tàbí àsìngbà lọ́jọ́ ọjọ́un?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Ologundudu, D. (2008). *The Craddle of Yorùbá Culture,* U.S., Center for Spoken Words/Institute of Yorùbá Culture.

Ọlájubù, O. (1975). *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*, Ìbàdàn, Longman Nig. Ltd.

Dáramọ́lá, O. àti Jẹ́jẹ́, A. (2014). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá,* Ìbàdàn, Oníbọn-òjé Press and Book Industries (Nig.). Ltd.

Owólabí, K. *et al* (2015). *Jẹ́ ká Bára Wa Sọ̀rọ̀ Ní Yorùbá, A Multidimentional Approach to the Teaching and Learning of Yorùbá As a Foreign Language.* Bloomington, Indiana, NALRC Press.

## MÓDÙ KẸTA

## ÌPÍN KẸRIN: ÀṢÀ OGE ṢÍṢE

***Àkóónú***

1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Irun Dídì

4.2 Aṣọ Wíwọ̀

4.3 Ìlẹ̀kẹ̀ (Ọrùn/Bèbè Ìdí)

44 Ara Pípa

4.5 Ara fífín

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Àṣà oge ṣíṣe jẹ́ àṣà Yorùbá pàtàkì ní ayé àtijọ́ àti lóde òní, bẹ́ẹ̀ ni oríṣiríṣi oge ṣíṣe ni ó wà ní ilẹ̀ káàárọ̀-oòjíire bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀nà tí a ń gbà ṣoge máa ń yàtọ̀ láti agbègbè kan sí òmìíràn nígbà mìíràn.

Nínú ìpín yìí ni a ti wo àwọn ọ̀nà tí Yorùbá máa ń gbà ṣoge àti ìyípadà tí ó dé bá àṣà yìí lóde òní. A wo àwọn oge ṣíṣe bíi ara sísọ, irun dídì, tìróò lílé, làálí lílé, bèbè sísín, nǹkan ìpara, irun fífá, ìlà kíkọ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

A tún le wo àṣà oge ṣíṣe yìí gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà láti mú kí ara mọ́, kí ó sì fa àwọn ènìyàn mọ́ra. Bí a bá ṣe lè ṣe oge sí bẹ́ẹ̀ ni àwọn ènìyàn yóò máa nífẹ̀ẹ́ wa níta. Èyí nìkan kọ́, oge ṣíṣe máa ń ṣe okùnfà ìlera. Ẹni tí ó bá ń tọ́jú irun orí rẹ̀ kò ní í ṣe alábàápàdé àrùn jẹrunjẹrun tàbí èkùsá bẹ́ẹ̀ ni ẹni tí ó bá ń lo àwọn nǹkan ìpara Yorùbá, ara rẹ̀ yóò máa dán, bẹ́ẹ̀ ni kò ni í ní àrùn kúrúnà.

Ṣùgbọ́n ṣá o, àṣejù oge máa ń wà fún ẹlòmíràn, pàápàá lóde òní, bẹ́ẹ̀ ni àṣà ọ̀làjú ti ṣe àkóbá fún àṣà oge ṣíṣe. Ẹlòmíràn lè kun ètè tàbí kí ó kun ojú kí ó wá dà bí ìdànǹdán, tí ènìyàn le má dá a mọ̀ mọ́.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Èròǹgbà wa nínú ìpín yìí ni:

- Láti jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mọ̀ nípa àṣà oge ṣíṣe láàrín àwọn Yorùbá lọ́jọ́ ọjọ́un.
- Kí a le ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn oríṣiríṣi oge tí Yorùbá máa ń ṣe.
- Láti fi àǹfààní tàbí ìwúlò tí ó wà nínú oge ṣíṣe hàn.
- Kí akẹ́kọ̀ọ́ le mọ àwọn àyípadà tí ó ti dé bá àṣà oge ṣíṣe ní àwùjọ Yorùbá lóde òní.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Kín ni oge ṣíṣe?
2. Dárúkọ àwọn ìlànà oge ṣíṣe àti bí wọ́n ti ń ṣe é ní agbègbè rẹ.
3. Oge ṣíṣe wo ni o fẹ́ràn jù àti ìdí tí ó fi rí bẹ́ẹ̀.
4. Àǹfààní wo ni ó wà nínú oge ṣíṣe?
5. Àwọn wo ni a ń pè ní ọmọge (ọmọ oge), kín sì ni ìdí tí a fi ń pè wọ́n bẹ́ẹ̀?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Irun Dídì

Àwọn obìnrin ni wọ́n sábà máa ń di irun orí wọn, bẹ́ẹ̀ ni oríṣiríṣi irun dídì ni ó wà. Irun dídì kò wọ́pọ̀ láàrín àwọn ọkùnrin àyàfi Baba Mọgbà. Ọkùnrin tí ó bá ti di irun orí rẹ̀, a jẹ́ pé ẹlẹ́sìn Ṣàngó ni.

Bí a bá ṣe àkíyèsí dáadáa, a ó rí i pé Ọlọ́run fún àwọn obìnrin ní irun gígùn, bẹ́ẹ̀ ni bí wọ́n bá di irun yìí tán, yóò máa wu takọ-tabo ni, pàápàá àwọn ọkùnrin, èyí sì máa ń fa kí àwọn ọkùnrin nífẹ̀ẹ́ irú àwọn obìnrin bẹ́ẹ̀. Bí wọ́n bá sì súnmọ́ ara, ó máa ń ṣe okùnfà ìgbéyàwó láàrín wọn.

Nígbà tí àwọn Òyìnbó aláwọ̀ funfun dé, tí a bẹ̀rẹ̀ sí i rí òwú ìkórun ni àwọn obìnrin mìíràn bẹ̀rẹ̀ sí i kó irun orí wọn. Láyé ìgbàanì, àwọn ìyá wa máa ń di irun orí wọn ni, ṣùgbọ́n èyí kò wọ́pọ̀ mọ́ láyé òde-òní. Jíjó ni àwọn obìnrin ń jó irun orí wọn lóde òni. Ẹlòmìíràn yóò sì jó o ní àwọ̀ tí ó bá wù ú. Ó lè sọ ọ́ di pupa tàbí funfun (àwọ̀ ewú). Irun wọn yóò wá jọ tí ewúrẹ́.

Ọ̀nà méta ni àwọn obìnrin ń gbà ṣe irun orí wọn lọ́ṣọ̀ọ́. Ọ̀nà kìnní ni bíba irun orí wọn. Èyí máa ń wáyé nígbà tí ojú bá ń kán obìnrin láti ṣe ohunkóhun pẹ̀lú irun rẹ̀. Dípò kí ó fi irun náà sílẹ̀ bẹ̀ẹ̀ yányán, wọn yóò kọ́kọ́ ba á kí wọn fi rí ààyè dì í.

Lọ́nà kejì, wọ́n le di irun orí wọn yìí, bẹ́ẹ̀ nì wọ́n lè fi òwú kó o. Bí wọ́n bá fẹ́ di irun oní wọn, wọ́n le dì í ní *'ṣùkú'* gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe àlàyé níwájú, wọ́n lè dì í ní *'pàtẹ́wọ́'*, wọ́n sì le dì í ní *'pánúmọ́'*. Wọ́n lè di irun wọn ní *'kòlẹ́sẹ̀'*, *'máforíbalẹ̀'*,

*'Òjòmápetí'*, *'Ìpàkọ́ ẹlẹ́dẹ̀'*, *korobá* tàbí *'kọ̀ǹkọ̀sọ̀'*, wọ́n sì le dì í ní *'alágogo'*, èyí tí àwọn ìyàwó tí wọ́n bá ń lọ sílé ọkọ máa ń di.

Ní ti àwọn ọkùnrin ẹ̀wẹ̀, kò sí àrà tí àwọn àgbà ọkùnrin ń fi irun orí wọn ṣe láyé àtijọ́ ju kí wọ́n fá a kodoro lọ, yóò sì máa dán yóò bíi kòlòǹjiá, bẹ́ẹ̀ ni àwọn tí wọ́n bá jẹ́ adóṣù òrìṣá kan le fa irun wọn ní apá kan kí wọ́n sì dá apá kan sí. Níbòmíràn, àwọn ìlàrí ọba aládé máa ń fá apá kan irun orí wọn, tí wọn yóò sì dá apá kan sí.

Ní ìparí, àṣà irun dídì gẹ́gẹ́ bí oge ṣíṣe ti ń yí padà lóde òní. Ọ̀pọ̀ àwọn obìnrin ni ó ń gẹ irun orí wọn bíi ti ọkùnrin lóde òní, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a kò tíì rí kí àwọn obìnrin máa fá irun orí wọn. Àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin púpọ̀ ní wọ́n máa ń fá irun orí wọn, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé láàrín àwọn àgbàlagbà ọkùnrin ni èyí wọ́pọ̀ sí ní ayé àtijọ́. Ohun mìíràn tí a tún ṣe àkíyèsí ni pé ọ̀pọ̀ àwọn ọ̀dọ́ òde òní ni wọ́n ń dá irungbọ̀n yàwìrì sí láìíṣe Lèmọ́mù. Ó le jẹ́ jẹ́ pé ohun tí ó fa èyí ni ojú ríro láti máa fá irun àgbọ̀n wọn lójoojúmọ́ tàbí lóòrèkóórè.

## 4.2 Aṣọ Wíwọ̀

Òwe Yorùbá kan sọ pé, *"Kí àgbàdó tó dáyé, nǹkan kan ni adìẹ ń jẹ"*. Èyí ni pé kí àwọn Òyìnbó aláwọ̀ funfun tó dé sí ilẹ̀ Yorùbá, kò sí ẹ̀yà tàbí ìran Yorùbá tí ń rin ìhòòhò. Bí àwọn ọkùnrin ti ní aṣọ tiwọn, bẹ́ẹ̀ ni àwọn obìnrin náà ní aṣọ tí wọ́n máa ń wọ̀.

Nígbà àtijọ́, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé bàǹtẹ́ ni àwọn àgbẹ̀ máa ń wọ̀ lọ sí oko, bẹ́ẹ̀ ni aṣọ kíjìpa ni a fi ń rán an. Wọn yóò so okùn méjì sí i ní igun méjèèjì tí ó ní, bẹ́ẹ̀ ni okùn wọ̀nyí ni wọn yóò máa fi so ó mọ́ ìdí. Irú aṣọ yìí kì í ṣe aṣọ tí a le wọ̀ ní ààrin ìlú, oko nìkan ni wọ́n máa ń ṣán bàǹtẹ́ lọ. Kò bójúmu tó láti máa ṣán bàǹtẹ́ wọ ààrin ìlú. Ìdí nìyẹn tí a ṣe máa ń pa á lówe pé *"àìfinipeni, àìféèyàn pèèyàn, ní í mú kí ará oko ṣán bàǹtẹ́ wọ̀lú"*. Ní àkókò yìí, aṣọ kíjìpá tí kò lè tètè gbó ni a máa ń dá fún aṣọ iṣẹ́. Èyí lè jẹ́ ṣòkòtò péńpé àti ẹ̀wu bùbá kékeré, bẹ́ẹ̀ ni aṣọ yìí kì í tètè ya bí ó bá kọ́gi. Ìdí nìyí tí wọn fi máa ń pè é ní *'akọ́gimáya'*.

Àwọn aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá mìíràn tí ó níyelórí ni *'dàńdógó'*, èyí tí ó máa ń tóbi gan-an. Àwọn aránṣọ máa ń farabalẹ̀ rán aṣọ yìí ni nítorí kò rọrùn láti rán. Ìdí nìyí tí

àwọn Yorùbá ṣe máa ń pa á lówe pé *'dàńdógó kọjá àbínúdá'*. Aṣọ àwọn olówó àti ọlọ́rọ̀ ni aṣọ yìí. Yàtọ̀ sí *'dàńdógó'*, aṣọ Yorùbá mìíràn tí ó tún ṣe pàtàkì ni *'Gbárìyẹ̀'*. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé *'gbárìyẹ̀'* kì í tóbi tó *'dàńdógó'*, òun náà máa ń tóbi, ó sì máa ń kan ìsàlẹ̀ ẹsẹ̀ dáadáa. Aṣọ mìíràn tí a tún lè tọ́ka sí ni *'agbádá'*. Kò sí irúfẹ́ aṣọ tí a kò̀ le fi rán *'agbádá'*, ìbáà ṣe aṣọ òkè, aṣọ àǹkárá tàbí léèsì.

Àwọn aṣọ mìíràn ni Ọ̀yàlà, Bùbá, Dàńṣíkí pẹ̀lú ṣòkòtò. Wọ́n lè wọ ṣòkòtò kẹ̀mbẹ̀ sí dàńṣíkí, kí wọ́n sì wọ ṣòkòtò sọ́ọ̀rọ̀ sí Bùbá.

Àwọn fìlà ti Yorùbá máa ń dé sí àwọn aṣọ wọ̀nyí ni *'Lábàǹkádà'* (abetí ajá), òrìbí, bẹntigọ́ọ̀ àti àkẹtẹ̀. Pàtàkì àwọn fìlà yìí ni pé bí Yorùbá bá wọ àwọn aṣọ tí a dárúkọ sókè yìí tí kò bá dé fìlà  síì, wọn kò ka irú ẹni bẹ́ẹ̀ sí ọmọlúàbí. Lẹ́yìn igbà tí ènìyàn bá wọṣọ tán, tí ó sì dé fìlà sí i ni a tó lè kà á sí ọmọlúàbí.

Aṣọ àwọn obìnrin kò fi bẹ́ẹ̀ pọ̀ tó ti ọkùnrin. Lára aṣọ tí àwọn obìnrin máa ń lò ni *'Tòbí'* tàbí *'Ìlábùrù'*, èyí ti wọ́n máa ń ṣán mọ́ ìdí pàápàá lẹ́nu iṣẹ́ wọn. Àwọn obìnrin tún máa ń ró *'aṣọ ìró'*, èyí tí wọ́n máa ń ró mọ́ ìdí wọn. Bí wọ́n bá ró aṣọ yìí, wọ́n ní láti wọ bùbá, èyí tí ó yàtọ̀ sí bùbá ti ọkùnrin. Lẹ́yìn èyí ni wọn yóò wé gèlè. Ó ṣeni láàánú pé ọ̀pọ̀ àwọn obìnrin ìwòyí ni kò mọ gèlè ní wíwé, ńṣe ni wọ́n máa ń lọ fi owó wé e lọ́dọ̀ àwọn tó kọ́ṣẹ́ gèlè wíwé.

Láyé àtijọ́, àwọn obìnrin máa ń wọ aṣọ kan ti a mọ̀ sí *'sinmí'*. Irúfẹ́ aṣọ yìí ni wọ́n máa ń wọ̀ sí aṣọ obìnrin tí ó bá ní ihò lára. Èyí ni kò ní í jẹ́ kí àwọn ènìyàn máa rí ara wọn níta bí wọ́n bá wọ irú aṣọ bẹ́ẹ̀.

Ní ìparí, àwọn obìnrin tún máa ń lo *'Ìbòrùn'* bẹ́ẹ̀ ni èjìká òsì ni wọ́n sábà máa ń filé. Èyí tí ó tún jẹ́ àṣà obìnrin ni wíwọ ìlẹ̀kẹ̀ àti ẹ̀gbà ọrùn, ki ìwọṣọ wọn le gún régé, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò fi *'Yẹrì'* sí etí wọn, wọn yóò lé tìróò, wọn yóò sì kun àtíkè fẹ́ẹ́rẹ́fẹ́ sí ojú wọn.

## 4.3 Ìlẹ̀kẹ̀

Gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe àlàyé lókè, àwọn obìnrin máa ń lo ìlẹ̀kẹ̀ oríṣiríṣi láti mú kí ìwọṣọ wọn dára síi. Nígbà mìíràn, wọ́n máa ń fi *'ike'* tàbí *'ẹ̀gbà'* sọ́rùn ọwọ́. Ní ayé àtijọ́, irin lásán ni wọ́n fi máa ń ṣe *'ẹ̀gbà'* ọwọ́ yìí, ṣùgbọ́n góòlù tàbí idẹ ni wọ́n ń lò lóde òni. Wọ́n gbàgbọ́ pé obìnrin ní láti to ọ̀pọ̀ ìlẹ̀kẹ̀ sí ìdí nítorí pe *"ìdí ti kò bá ní*

*ìlẹ̀kẹ̀ bí orógùn ọkà ní í rí"*. Àwọn ìlẹ̀kẹ̀ bí i *'lágídígba'* gẹ̀dẹ̀ àti Jòjò ni àwọn obìnrin máa ń fi sí ìdí.

Àwọn obìnrin máa ń lo yẹrì etí láti mú kí ojú wọ́n dára sí i bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ẹ̀sìn ìgbàlódé kan kò fi ara mọ́ èyí. Yàtọ̀ sí ti ẹ̀sìn, àwọn kan máa ń sọ pé yẹrì etí máa ń dégbò sí wọn léti bí wọ́n bá lò ó. Nítorí ìdí èyí, wọ́n máa ń sá fún yẹrí etí yìí.

Obìnrin ni ó máa ń lo yẹrí etí, ṣùgbọ́n èké ti dáyé, aásàà ti dé Apòmù ni ọ̀rọ̀ yẹrí etí jẹ́ lónìí nítorí pé ọ̀pọ̀ àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin òde òní ń lu etí, tí wọ́n sì ń lo yẹrí, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ojú àbùkù ni àwùjọ fi máa ń wo irú àwọn ọ̀dọ́ bẹ́ẹ̀.

Yàtọ̀ sí ìlẹ̀kẹ̀ ọrùn àti ọwọ́, àwọn obìnrin mìíràn tún máà ń kó ìlẹ̀kẹ̀ sí ìdí wọn, èyí tí wọ́n ń pè ní **bèbè ìdí**. Èyí ni ìlẹ̀kẹ̀ tí àwọn obìnrin máa ń kó sídìí tí ìdí wọn yóò fig a díẹ̀ sí i. Bí wọ́n bá ti ṣe èyí tán, wọn yóò máa sún bèbè náà sí ìsàlẹ̀ tàbí sókè nígbà tí ó bá yẹ. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé bèbè ìdí yìí kì í hàn síta, àwọn obìnrin gbà pé bí ọkọ wọn tàbí olólùfẹ́ wọn bá le rí i ní ìdí àwọn, yóò túbọ̀ nífẹ̀ẹ́ àwọn sí i. Èyí nìkan kọ́, àwọn obìnrin kan ń lu imú láti lè mú kí àwọn olólùfẹ́ tàbí ọkọ wọn fà mọ́ wọn sí i. Àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin òde òní fẹ́ràn bèbè bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé fún ìṣekúṣe ni ọ̀pọ̀ wọn fi ń ṣe èyí. Ṣùgbọ́n àwọn ìyá wa tí wọ́n máa ń sín bèbè kì í ṣe nítorí ìṣekúṣe bí kò ṣe oge. Àṣejù ni àwọn ọ̀dọ́bìnirn òde òní fi bọ̀ ọ́.

## 4.4 Àwọn Ohun Ìpara

Oríṣíríṣí àwọn nǹkan olóòórùn dídùn ni àwọn Yorùbá fi máa ń pa ara láyé àtijọ́ kí ó lè mú ara wọn dán, kí ó sì jọ̀lọ̀. Wọ́n máa ń lo gbígbá epo pupa, osùn, àdí àgbọn, òróró, òrí àti àwọn nǹkan ìpara mìíràn.

Bákan náà, àwọn obìnrin máa ń lé làálì sí àtẹ́lẹsẹ̀ àti sí àtẹ́lẹwọ́ wọn, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn mìíràn gbà pé títọ́ làálì yìí ni wọ́n gbé wọ àṣà oge ṣíṣe Yorùbá láti ọ̀dọ̀ àwọn Tápà àti àwọn Ilọrin.

Bẹ́ẹ̀ ni tìróò lílé náà jẹ́ ọ̀kan nínú bí wọ́n ṣe ń fún ara lóge. Bí wọ́n ṣe ń lé tìróò yìí fún ọmọdé, bẹ́ẹ̀ ni àwọn àgbàlagbà náà ń lé tìróò. Nígbà mìíràn, tìróò lílé lè wà fún òògùn ojú pàápàá tí nǹkan bá kó sí ẹnìkan lójú. Wọn yóò sọ pé kí ó lọ lé tìróò kí pàǹtí náà lè yọ kúrò nínú ojú onítọ̀hún.

Báyìí, ọ̀làjú ti jẹ́ kí tíróò lílé dínkù nítorí pé lẹ́ẹ̀dì àwọn Òyìnbó ni àwọn obìnrin fi ń kun ojú wọn, bẹ́ẹ̀ ni lẹ́ẹ̀dì yìí ni wọn fi ń kun ètè méjèèjì yoyooyo.

Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, osùn ni àwọn Yorùbá fi máa ń pa ara ọmọ kékeré àti àgbà. Wọ́n gbà pé osùn yìí yóò máa mú wọn dán, tí yóò sì máa mú ara jọ̀lọ̀. Wọ́n tún máa ń lo **àdí-àgbọn** láti mú kí ara dán bẹ́ẹ̀ ni ọ̀pọ̀ ni ó sì ń lo àdí àgbọn lónìí nítorí pé wọn gbàgbọ́ pé ó ń ṣe ìwòsàn fún ẹran ara. Ó ń mú kí ẹran àti awọ ara jọ̀lọ̀ tàbí dán dáadáa.

Àwọn Yorùbá ni wọ́n ni osùn kíkùn ní ìkáwọ́, bẹ́ẹ̀ ni ibi tí a bá gbé ń ṣe àjọyọ̀ oyè tàbí ti ìyàwó tàbí ti ọmọ titun ni a ti máa ń kun osùn. Ó jẹ́ àṣà pé abiyamọ gbọ́dọ̀ kun osùn láàrín àwọn Yorùbá láyé àtijọ́. Bí ó sì ti ń kun osùn yìí fún ara rẹ̀, ni yóò máa kùn fún ọmọ rẹ̀ pẹ̀lú. Ìdí nìyẹn tí Yorùbá ṣe máa ń sọ pé *'kì í tán nígbà osùn, kí á má rí fi pa ọmọ lára'*. Bẹ́ẹ̀ ni bí Yorùbá bá ń ṣe àdúrà fún àwọn àgàn, wọn yóò sọ pé *'Àgàn tí kò ì bí, yóò ti ọwọ́ àlà bosùn"*. Èyí túmọ̀ sí pé àgàn yóò bí ọmọ, yóò sì kun ọmọ náà ní osùn.

## 4.5 Ara Fífín Gẹ́gẹ́ bí ara Àṣà Oge Yorùbá

Ara fífín náà jẹ́ ìlànà oge ṣíṣe láàrín àwọn Yorùbá ní ayé àtijọ́. Àwọn olóólà ní wọ́n sábà máa ń fínra fún àwọn obìnrin, èyí tí ó máa ń bùkún ẹwà wọn. Ènìyàn lè fín iwájú, ní apá ibi tí irun iwájú máa ń kún dé. Oríṣi bátànì tí wọ́n fi máa ń fín irun ni:

(a) Orúkún aro

(b) Ẹlẹ́ẹ̀ta àti

(d) Elégèé

Ní ayé ìgbàànì, ènìyàn tún lè fín inú. Ohun tí wọ́n sábà máa ń fín sínú ni *'Ọmọláńgidi'*, tàbí *'Aláǹgbá'*. Yàtọ̀ sí inú, ènìyàn tún lè fín ẹ̀yìn. Wọn yóò sá ẹ̀yìn ní gbẹ́rẹ́ tí wọn yóò fi oríṣíṣi bátànì ṣe e lọ́sọ̀ọ́. Ẹ̀yìn fífín yìí lè púpọ̀ nítorí pé, ọ̀sẹ̀ méjì tí èèyàn bá fín ẹ̀yìn tán, kò ní í le ṣe nǹkankan, àtiyínrùn rẹ̀ yóò di agbára nítorí egbò tí yóò wà níbẹ̀. Wọ́n tún máa ń fín *'tọwọ́bojú'*, tí yóò bẹ̀rẹ̀ ní ọ̀kánkán ihò etí lọ sí ẹyinjú ọ̀tún àti tòsì.

Ní ti ara sisọ àti ojú sísọ, (ojú sísọ ni fifi abẹ kọ ilè tín-ín-tìn-tùn-tún sí àwọn ẹ̀yà ara kan. Ó wọ́pọ̀ láàárín àwọn Ìbàdàn, Èkìtì, Ìjẹ̀sà abbl. Ènìyàn lè sọ ẹ̀yìn, ọwọ́,

ìtàn, ọ̀pọ̀lọ́ṣẹ̀, ojú tàbí ọrùn ọwọ́. Irú èyí sábà máa ń wáyé nígbà tí ìyàwó bá ń palẹ̀mọ́ fún lílọ sí ilé ọkọ rẹ̀.

Yorùbá tún máa ń ṣe iná ọ̀rẹ́ sí ẹ̀yìn ọwọ́ fún ọ̀ṣọ́ ara àti láti lè mú kí ara lẹ́wà, bẹ́ẹ̀ ni àwọn obìnrin tún máa ń lo ẹ̀lẹ̀ títóbi láti fi bọ osì ọ̀tún àti ẹ̀lẹ̀ tẹ́ẹ́rẹ́ tí wọn yóò fi bọ ọwọ́ ọ̀tún. Yàtọ̀ sí èyí, àwọn ìyàwó yóò fi orúka ẹ̀lẹ̀ bọ ìka ọ̀tún àti tòsì, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ní láti fi yẹtí bọ ihò etí wọn. Góòlù ni wọn ń ló gẹ́gẹ́ bí ẹ̀lẹ̀ ìbowọ́ tàbí ìbọka láyé òde-òni.

Ní ìparí, a ó ṣe àkíyèsí pé ọ̀pọ̀ nǹkan ló ti ń yí padà nígbà tí ọ̀làjú ti dé, bẹ́ẹ̀ ni a kò fi bẹ́ẹ̀ fín ara mọ́ bí a bá yọ ti àwọn ọ̀dọ́ tí wọn ń ṣoge agándáńgbọ́n tàbí àwọn tí wọ́n wọ ẹgbẹ́ ìmùlẹ̀, tí wọ́n sì ń fi ara wọn fún oríṣiríṣi àmí ìdánimọ̀ nípa ara fínfín lónìí.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín yìí ni a ti wo onírúurú ìlànà àṣà oge ṣíṣe láàrín àwọn Yorùbá ní ayé àtijọ́. A ṣe àlàyé, a sì wo àwọn ìlànà oge ṣíṣe láyé àtijọ àti ìdí tí wọ́n fi ń ṣe àwọn nǹkan wọ̀nyí.

Lára àwọn àṣà oge ṣíṣe tí a mẹ́nubà ni àṣà irun dídì láàrín àwọn obìnrin àti orúkọ onírúurú irun tí wọ́n máa ń dì nígbà náà. A tún wo àṣà aṣọ wíwọ̀ nígbà tí a sọ̀rọ̀ lórí oríṣiríṣi aṣọ tí Yorùbá máa ń wọ̀ àti orúkọ wọn.

A sọ̀rọ̀ lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́ lórí ìlẹ̀kẹ̀ lílò ní ayé ìgbaànì àti onírúurú ìlẹ̀kẹ̀ tí àwọn Yorùbá máa ń lò, bẹ́ẹ̀ ni a wo bí àwọn Yorùbá ṣe máa ń fi nǹkan para láti mú kí ara wọn jọ̀lọ̀. Èyí nìkan kọ́, a wo àwọn ọ̀nà tí Yorùbá ń gbà ṣe oge nípa ara fínfín, èyí tí ó máa ń bu ẹwà kún ẹwà àwọn ènìyàn yìí. Ní ìparí, a ṣe àlàyé bí àyípadà ṣe ń dé bá àwọn àṣà yìí bóyá nípa ìtẹ̀síwájú ni tàbí nípa ìfàsẹ́yìn.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣe àlàyé kíkún lórí ipò tí àṣà irun dídì wà lóde òní.
2. Sọ̀rọ̀ sóké lórí aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá àti pàtàkì wọn lóde òní.
3. Kín ni ìdí rẹ̀ tí wọ́n fi máa ń sọ pé *'Dàńdóógó kọjá àbínúdá'?*

4. Àwọn oge àtijọ wo ni ó yẹ kí a fagilé lóde òní àti pé kín ni ìdí tí o fi sọ bẹ́ẹ̀?

5. Àwọn ìyàtọ̀ wo ló wà nínú pípa ara àti nǹkan ìpara láyé àtijọ́ àti lóde òní?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Dáramọ́lá, O. & Jẹ́jẹ́, A. (2014). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọn-Òjé Press.

Sàlámì, A. (1989). "Àṣà Òge Ṣíṣe Ní Ilẹ̀ Káàárọ̀ Oòjire", ní *Fèyíkọ́gbọ́n,vol. 20, No. 1*, Ìbàdàn, Comedy Publications Company.

Ọlájubu, O. (1975). *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn, Longman.

Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn, Gavima Press Ltd.

Ọyádèjì, B. (1990). *Ọdún Òkè-èbàdàn Ní Ìlú Ìbàdàn*. Ìbàdàn Comedy Publications Company.

Àbẹ̀jẹ́, F. (1989). "Àṣà Ilà Kíkọ Ní Ilẹ̀ Yorùbá", ní *Fèyíkọ́gbọ́n,vol. 20, No. 3,* Ìbàdàn, Comedy Publications Company.

**MÓDÙ KẸTA**

## ÌPÍN KARÙN-ÚN: ÀWỌN OÚNJẸ ILẸ̀ YORÙBÁ

***Àkóónú***

1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Iṣu àti Àwọn Oúnjẹ tí à ń fi wọn ṣe?

4.2 Gbágùdá àti àwọn Oúnjẹ tí a n fi wọn ṣe?

4.3 Àgbàdo àti Àwọn Oúnjẹ tí a ǹ fi wọ́n ṣe?

44 Ẹ̀wà àti Àwọn Oúnjẹ tí a ń fi wọ́n ṣe?

4.5 Èso, Ewébẹ̀ àti Àwọn Ohun Mímu.

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Àṣà tí ó jẹ mọ́ oúnjẹ jíjẹ ni a gbéyẹ̀wò nínú ìpín yìí níbi tí a ti ṣe àlàyé oríṣiríṣi lórí irúfẹ́ oúnjẹ Yorùbá. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ síwájú, iṣẹ́ àgbẹ̀ ni iṣẹ́ tí Yorùbá yàn láàyò ní ayé àtijọ́ àti lóde òní pẹ̀lú, bẹ́ẹ̀ ni onírúurú àwọn ohun ọ̀gbìn oúnjẹ ni wọ́n ń pèsè fún àwùjọ láti fi gbé inú ró. Èyí wáyé nípa àǹfààní agbègbè tí Olódùmarè dá wọn sí àti irúfẹ́ ilẹ̀ tí Ọlọ́run fi jíǹkí wọn.

A wo ìpèsè oúnjẹ bí iṣu èyí tí a máa ń gbìn ní àwọn agbègbè kan bíi Èkìtì, Òkè-Ògùn àti àwọn ibòmíràn tí ilẹ̀ ti dára fún iṣu gbígbìn, tí wọ́n sì ń pèsè rẹ̀ ní ọ̀pọ̀lọpọ̀, èyí tí ó mú kí wọ́n tún máa tà á fún àwọn agbègbè mìíràn.

A kò ṣàìmẹnubá àwọn onírúurú oúnjẹ tí ó máa ń jáde lára iṣu àti bí a ṣe ń pèsè wọn fún jíjẹ àti fún títà. Ìdí nìyí tí a ṣe máa ń tọ́ka sí agbègbè Èkìtì gẹ́gẹ́ bí èyí tí iṣu gbígbìn ti jẹ́ iṣẹ́ pàtàkì nínú ìpèsè oúnjẹ wọn tí ó sì jẹ́ àṣà fún wọn láti máa jẹ iyán ní gbogbo ìgbà.

A tún sọ̀rọ̀ nípa ìpèsè gbágùúdá tàbí ẹ̀gẹ́ tí ó jẹ́ pàtàkì oúnjẹ ní agbègbè mìíràn àti àwọn ohun oúnjẹ tí a ń pèsè láà ara rẹ̀. Bákan náà ni a ṣe àlàyé lórí irúfẹ́ èròjà oúnjẹ mìíràn bí i ẹ̀wà, ọ̀gẹ̀dẹ̀ àti àwọn ohun tí a ń lò ó fún láti pèsè oúnjẹ tí ó ṣe ara lóore.

Ní iparí ni a mẹ́nuba àwọn ohun mímu tí ó gbajúmọ̀, èyí tí àwọn Yorùbá máa ń mu láti mú ayọ̀ wọn kún sí i, pàápàá ní àkókò ayẹyẹ ọdùn, ìgbéyàwó, ìsìnkú àgbà, oyè jíjẹ tàbí níbi ilé ṣíṣí. Gbogbo èyí ló mú wa rántí àṣà oúnjẹ jíjẹ àti àwọn oúnjẹ tí a ń jẹ ní Ilẹ̀ Yorùbá láyé àtijọ́ àti lóde òní.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lára èròǹgbà tí a ní lórí ìpín yìí ni:

- Kí akẹ́kọ̀ọ́ lè mọ àwọn oúnjẹ Yorùbá láyé àtijọ́ àti lóde òní.
- Kí àwọn òǹkàwé yìí le mọ oúnjẹ tí ó gbajúmọ̀ jù lọ ní agbègbè kọ̀ọ̀kan ní ilẹ̀ Yorùbá.
- Láti mú kí akẹ́kọ̀ọ́ tàbí òǹkàwé mọ irúfẹ́ oúnjẹ àti àwọn ohun tí a ń lò wọ́n fún.

- Kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tàbí òǹkàwé le mọ ipò tí ìpèsè àti jíjẹ àwọn oúnjẹ wọ̀nyí wà lóde òní.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Àwọn oúnjẹ wo ni ó ń jáde lára iṣu?
2. Agbègbè Ilẹ̀ Yorùbá wo ni ìpèsè iṣu pọ̀jù sí láyé àtijọ́ àti láyé òde-òní?
3. Irúfẹ́ àwọn oúnjẹ wo ni a lè fi àgbàdo ṣe?
4. Oríṣi ẹ̀wà mélòó ni ó wà àti pé àwọn oúnjẹ wo ni a ń fi ẹ̀wà ṣe?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Iṣu àti àwọn oúnjẹ tí à ń fi iṣu ṣe?

Iṣu jẹ́ oúnjẹ tí àwọn Yorùbá gbà gẹ́gẹ́ bí ọba láàrín àwọn ọ̀gbìn oúnjẹ, bẹ́ẹ̀ ni oríṣirísi iṣu ni ó wà-iṣukọ tàbí akọ iṣu, ewùrà, èsúrú, kókò, àti ànàmọ́. Nínú àwọn iṣu wọ̀nyí, iṣukọ ni ó gbajúmọ̀ jù fún oúnjẹ pàápàá tí wọ́n bá ti gún un ní iyán. Iyán iṣukọ yìí ni ó máa ń dára ju iyán ewùrà lọ nítorí pé òun ni kì í ní kókó bí iyán iṣu ewùrà. Ìdí nìyí tí Yorùbá ṣe máa ń pa á lówe pé *"a kì í mọ̀-ọ́ngún mọ-ọ́ntẹ̀ kí iyán ewùrà má ní ẹmọ (kókó)"*. Yàtọ̀ sí iyán iṣukọ àti iyán ewùrà, Yorùbá tún máa ń gún iyán kókò, èyi ni wọ́n gbàgbọ́ pé ó máa ń fún wọn ní ìlera pípé. Nínú àwọn iṣu yìí, iṣu eṣúrú àti iṣu ànàmọ̀ jẹ́ èyí tí wọn kì í fi gúnyán fún ìdí kan tàbí òmíràn. Ìdí nìyí tí wọ́n ṣe máa ń pa a lówe pé *"èsúrú ṣàṣejù, ó tẹ́ lọ́wọ́ oníyán"*. Bóyà ìdí ni pé rírọ̀ ni àwọn iṣu wọ̀nyí máa ń rọ̀ bí wọ́n bá fi wọ́n gúnyán.

A lè jẹ iṣukọ yìí nìkan, bẹ́ẹ̀ ni a lè gún un níyán jẹ. Oríṣiríṣi iṣukọ ni ó wà – Efùrù, ọ̀dọ, Arẹ́yìngbakùmọ̀, ìgángán ọlọ́bẹ̀-kú-àṣẹ̀nù àti pètísán, ṣùgbọ́n Yorùbá gbà pé àwọn iṣu tí ó dára jù lọ láti fi gúnyán ni Efùrù, ọ̀dọ àti arẹ́yìngbakùmọ nítorí pé bí wọ́n ṣe ń gún un ni yóò máà gba omi, tí wọn yóò sì máa wú fùùù. Bí a bá rí obìnrin tí ó mọ iyán gún dáadáa, bí ó bá gún iṣu arẹ́yìngbakùmọ̀, iyán rẹ̀ máa fẹ́lẹ́ bí ẹ̀dọ̀ ẹran ni. Àwọn iṣu bí Ọlọ́bẹ̀-kú-àṣẹ̀nù àti pètísán kò dára fún iyán bí ko ṣe jíjẹ níṣu. Wàyí ò, a kò gbọdọ̀ gbàgbé láti ṣe àlàyé pé bí a ṣe ní iṣukọ funfun bẹ́ẹ̀ ni pupa wa, bí a sì ṣe ní èṣúrú pupa náà ni a ní èsúrú funfun, bẹ́ẹ̀ ni kókò pupa àti kókó funfun wà pẹ̀lú.

Gbogbo wọn ló dára lára. Ṣùgbọ́n ṣá o, ẹ̀yà èṣúrú kan wà tí wọ́n ń pé ní *'gùdùgúdú'* wọn kì í jẹ gùdùgúdú nítorí májèlé ni, ṣùgbọ́n wọ́n máa ń fi ṣe òògùn.

Yàtọ̀ sí kí á gún iṣu fún iyán jíjẹ, a máa ń lo iṣu yìí kan náà fún àsáró tàbí ẹ̀bẹ. Èyí ni pé, bí a bá ti ṣe iṣu jinná tán, a ó bu epo tàbí ata lé e lórí, a ó fí orógùn tàbí síbí rò ó pọ̀ títí yóò fi di àsáró, tí a ó sì máa jẹ ẹ́. Iṣu yìí kan náà ni a le bẹ èèpo ẹ̀yìn rẹ̀ dànù, kí á sá a gbẹ dáadáa, kí a lọ̀ ọ́, kí a sì rò ó ní àmàlà, èyí tí ó wọ́pọ̀ nínú oúnjẹ Yorùbá láyé àtijọ́ àti lóde òní. Èyí ni wọ́n máa ń pè ní *'èlùbọ́ iṣu'*. Yàtọ̀ sí àṣáró, a lè fi epo dín iṣu yìí kan náà ní *'dùndú'*, kí á sì jẹ ẹ́. Ní ti iṣu ewùrà, àwọn ẹ̀yà Ìjẹ̀bú máa ń fi iṣu yìí ṣe oúnjẹ kan tí a ń pè ní *'Ìkọ́kọrẹ́'*, bẹ́ẹ̀ oúnjẹ yìí ṣe pàtàkì láàrín àwọn ẹ̀yà yìí.

Ní àkóótán, ó jẹ́ àṣà Yorùbá láti máa ṣe ọdún iṣu káàkiri Ilẹ̀ Yorùbá nítorí ipò pàtàkì tí wọ́n tó oúnjẹ yìí sí. Ní àkókò ti iṣu tuntun bá fẹ́ jáde, kò sí ẹni tí ó gbọdọ̀ jẹ iṣu kí ọba tó jẹṣu, lẹ́yìn tí ọdún yìí bá rékọjá ní oṣù kẹfà sí oṣù kẹjọ ọdún. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ni kò ka èèwọ̀ yìí sí mọ́ lóde òní, pàápàá ní àwọn ìlú ńláńlá, àwọn ènìyàn ìlú kéréje àti ìletò sì ń tẹ lé àṣà yìí.

## 4.2 Gbágùúdá àti àwọn oúnjẹ tí à ń fi ló ṣe

Oúnjẹ pàtàkì mìíràn yàtọ̀ sí iṣu ni *'gbágúdá'* tàbí *'ẹ̀gẹ́'*. Ní agbègbè mìíràn, *'pákí'* ni wọ́n máa ń pè é. Ohun tí ó ṣe pàtàkì ni pé jákèjádò ilẹ̀ Yorùbá ni wọ́n ti ń gbin gbágùdá, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ohun tí wọ́n fi ń ṣe tàbí oúnjẹ tí wọ́n ń lò ó fún lè yàtọ̀ díẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, *'gààrí'* ni wọ́n máa ń fi gbágùdá ṣe ní agbègbè Èkìtì, Òkìtìpupa, Ìjẹ̀bú, Ẹ̀gbá Ọ̀yọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Gààrí wúlò láti máa fi rẹ̀ngbẹ ní àsìkò ooru tàbí ọ̀gbẹlẹ̀. A lè da gààrí sínú omi tútù, kí á sì máa fi ọwọ́ tàbí ṣíbí mu un. Bí a bá rí ẹja gbígbẹ, ẹran díndín, àkàrà tàbí mọ́ínmọ́ín, a ó gbádùn gààrí gẹ́gẹ́ bí oúnjẹ tàbí ìpanu. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, gaan ni a sábà máa ń fi gààrí tẹ̀ ẹ̀bà láti fúnní ní okun àti agbára tí ó yẹ. A ó rí i pé ẹ̀bà rọrùn láti rò ju àmàlà lọ nítorí pé bí a bá ti gbé omi ka orí iná, tí ó bá hó, a ó kan da gààrí sínú omi náà ni, bẹ́ẹ̀ ni ẹ̀bà dé nìyẹn. Nígbà mìíràn, a máa ń fẹ́ láti jẹ ẹ̀bà ju iyán lọ.

Láàrín àwọn Ẹ̀gbá àti Ẹ̀gbádò (Yewa) èlùbọ́ Láfún ni wọ́n máa ń fi gbágùdá ṣe, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń ro èlùbọ́ láfún yìí nínú omi hího bí a ti ń ro àmàlà àti ẹ̀bà ni. Láàrín àwọn Yorùbá Èkó, fùfú ni wọ́n máa ń pe láfún yìí. Láfún máa ń funfun pìn-ín

bí iyán ni, bẹ́ẹ̀ ni a le fi ọbẹ̀ kan náà jẹ iyán àti láfún. Wọ́n tún máa ń fi gbádùdá ṣe *'fùfú'*, èyí tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn máa ń rò pé iyán ni.

Oríṣi gbágùdá méjì ni ó wà. Ọ̀kan wà tí wọ́n ń pè ní *'Iṣu-nìkàn-kíyán'*, èyí tí wọ́n máa ń jẹ níṣu tí wọ́n tún máa ń gún un ní iyán. Irúfẹ́ gbágùdá yìí yàtọ̀ sí èyí tí wọn fi máa ń ṣe èlùbọ́ láfún nítorí pé bí wọ́n bá jẹ irúfẹ́ gbágùdá yìí ní iṣu, wọn kò gbọdọ̀ jẹ́ èyí tí wọ́n fi ń ṣe gààrí yẹn níṣu nítorí pé májèlé wà nínú rẹ̀. Ṣùgbọ́n ní ti *'iṣu-nìkàn-kíyán'*, a lè jẹ́ ẹ níṣu. A lè fi ọbẹ̀ tàbí epo tí a bá fi jẹ àwọn iṣu yòókù náà jẹ iṣu-nìkàn-kíyán láìsí ewu rárá.

## 4.3 Àgbàdo àti àwọn ohun tí a ń fi àgbàdo ṣe

Àgbàdo náà jẹ́ ohun ọ̀gbìn pàtàkì kan tí ó gbajúgbajà ní ilẹ̀ Yorùbá láyé àtijọ́ àti lóde òní. Àgbàdo jẹ́ ọ̀gbìn kan tí àwọn àgbẹ̀ máa ń gbìn lẹ́ẹ̀mejì ní àárin ọdún. Bí wọ́n tí ń gbin àgbàdo òjò ni wọ́n ń gbin àgbàdo ẹ̀ẹ̀rùn. Bí àgbàdo bá ṣẹ̀ṣẹ̀ gbó, tí ó wà ní tútù, a lè sè é jẹ, kí á sì gbádùn rẹ̀ bí oúnjẹ.

Ọ̀nà mìíràn tí a lè gba lo àgbàdo gẹ́gẹ́ bí oúnjẹ ni kí á fi ṣe ògì ẹ̀kọ. Wọ́n máa ń po ògì yìí pẹ̀lú omi gbígbóná tí ó ti hó lórí iná, tí wọn yóò sì da ògì sí i. Ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá ṣe máa ń sọ pé *'bí Òyìnbó bá mu tíì (tea), mà mú ẹ̀kọ gbígbóná, omi gbígbóná ni a jọ ń mu"*. Ìyẹn ni pé bí àwọn Òyìnbó aláwọ̀ funfun ṣe ń mu tíì láti ṣẹ́gun òtútù, bẹ́ẹ̀ ní àwọn Yorùbá náà máa ń fi ẹkọ gbígbóná lé òtútù lọ, pàápàá ní àkókò ọyẹ́ tàbí ọ̀gìnnìtìn. Ọ̀pọ̀ ni ó máa ń fi ọ̀lẹ̀lẹ̀ tàbí mọ́ínmọ́ín tàbí àkàrà mu ẹ̀kọ́ tí wọn yóò sì yó digbí. Nígbà mìíràn, àwọn ìyá àgbà tàbí abilékọ máa ń pọ́n ẹ̀kọ gbígbóná, yóò sì di ẹ̀kọ tútù, èyí tí ó jẹ́ iṣẹ́ òòjọ́ fún wọn. Bí a bá ṣe àkíyèsí, a ó rí i pé ẹ̀kọ tútù ti di oúnjẹ fún tọmọdé tàgbà lónìí.

Nígbà mìíràn, wọ́n le fi àgbàdo ṣe ẹ̀wà àdàlú, ìyẹn ni ẹ̀wà àti àgbàdo tí a se papọ̀ tí ó di oúnjẹ. Wọ́n tún máa ń fi àgbàdo ṣe gúgúrú, èyí tí wọ́n fi máa ń ṣe ìpanu, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n lè fi ṣe ààdùn, tí í ṣe ìpanu bakan náà. A kò gbọdọ̀ gbàgbé pé àwọn ènìyàn máa ń fi àgbàdo ṣe oúnjẹ kan tí wọ́n ń pè ní *'ègbo'*, tí wọn yóò bu ọbẹ̀ lé lórí, kí wọ́n tó máa jẹ ẹ́ gẹ́gẹ́ bi oúnjẹ ajẹgbádùn. Wọ́n máa ń fi àgbàdo ṣe tepotiyọ, èyí tí wọn yóò lọ àgbàdo, tí wọn yóò fi epo sí i, tí wọn yóò sì pọ́n ọn bí mọ́ínmọ́ín erèé.

## 4.4 Ẹ̀wà àti àwọn oúnjẹ tí a ń fi ẹ̀wà ṣe.

Ẹ̀wà jẹ́ oríṣí oúnjẹ kan tí a kò lè fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn bí a bá ń sọ̀rọ̀ àwọn oúnjẹ ilẹ̀ Yorùbá. Àwọn onímọ̀ ìṣègùn Òyìnbó tilẹ̀ sọ pé ẹ̀wà jẹ́ oúnjẹ tí ó ṣe ara lóore ju gbogbo oúnjẹ́ yòókù lọ. A gbọ́ pé nǹkan bí ẹgbẹ̀rún mẹ́ta ni oríṣi ẹ̀wà tí a mọ̀ ní àgbáyé, ṣùgbọ́n díẹ̀ ni a mọ̀ tàbí tí ó wà ní Ilẹ̀ Yorùbá. Nínú àwọn tí a máa ń gbọ́ orúkọ wọn tàbí tí ó wà ní àrọ́wọ́tó wa ni ẹ̀wà erèé àti ẹ̀wà awújẹ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a sẹ̀sẹ̀ ń mọ̀ nípa ẹ̀wà sóyà láìpẹ́ ni.

Onírúurú ìtàn ni ó so mọ́ ẹ̀wà àti òrìṣà ìbejì ní ilẹ̀ Yorùbá. A ó ṣe àkíyèsí pé lára àwọn ọ̀kànlénú irúnmọlẹ̀ Yorùbá ni ìbejì wà. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń se ẹ̀wà fún ìbejì láyé àtijọ́ tí wọ́n sì máa ń kọrin pé;

> Epo ń bẹ
> Ẹ̀wà ń bẹ o
> Epo ń bẹ
> Ẹ̀wà ń bẹ o
> Àyà wa ò jáá
> Àyà wa ò já láti bíbejì
> Epo ń bẹ
> Ẹ̀wà ń bẹ o

Orin òkè yìí fihàn wá pé ẹ̀wà ni oúnjẹ àwọn ìbejì àti pé àwọn ìyá wọn náà ní láti máa jẹ ẹ̀wà ní àsìkò tí wọ́n bí àwọn ọmọ wọ̀nyí kí ara tiwọn náà le tètè mókun. Nítorí náà àwọn tí ó bá bí ìbejì gbọ́dọ̀ máa kẹ́ wọn, kí wọn sì máa gẹ̀ wọ́n, kí wọ́n máa baà rí ìbínú wọn.

Ẹ̀wà erèé gbajúgbajà ní àwùjọ Yorùbá títí di oní olónìí, wọ́n sì fi máa ń ṣe oríṣiríṣi oúnjẹ nínú ilé, àti níta. Bí àpẹẹrẹ, wọ́n le se ẹ̀wà erèé jẹ́ lásán, kí wọn da epo tàbí ata lé e lórí, kí wọ́n sè é jẹ. Wọ́n le fi ẹ̀wà erèé mu gààri, wọ́n sì lè fi jẹ ẹ̀kọ tútù. Wọ́n tún máa ń fi ẹ̀wà erèé ṣe mọ́ínmọ́ín elépo tàbí mọ́ínmọ́ín olóròòró. Èyí nìkan kọ́, wọ́n lè fi ẹ̀wà erèé dín àkàrà kengbe tàbí àkàrà sẹ̀ẹ̀kẹ́. Wọ́n lè se é ní ẹ̀wà tumpúlu, wọ́n sì lè se é ní ẹ̀wà wooro.

Bákan náà, Yorùbá máa ń se ẹ̀wà awújẹ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀wà erèé náà ni. Wọ́n máa ń fi ṣe àdàlú mọ́ àgbàdo tútù tàbí kí wọ́n fi epo àti ata sí i kí wọ́n sè é ní òmóòyò. Nígbà mìíràn, wọ́n le jẹ ẹ̀wà àti iṣu papọ̀ lẹ́yìn tí wọ́n ti sè wọ́n lọ́tọ̀ọ̀tọ̀ , tí wọ́n sì dà wọ́n papọ̀ sí ojú kan. Lára àwọn oúnjẹ tí Yorùbá ń lo ẹ̀wà erèé fún ni *'èkuru'*. Bí wọ́n bá ti

lọ erèé tán, dípò tí wọn ìbá fi epo, ìyọ̀ àti èròjà mìíràn sí i, wọ́n yóò kan fi ìyọ̀ lásán sí ni, wọn yóò sì fi orógùn pò ó pọ̀ dáadáa, kí wọ́n tó pọ́n ọn sínú ewé gbòdògì, tí wọn yóò sì sè é lórí iná. Àádùn náà jẹ́ ọ̀kan nínú oúnjẹ tí wọ́n máa ń lo erèé mọ́, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọn yóò lọ̀ ọ́ mọ́ àgbàdo gbígbẹ ni. Wọ́n lè fi èkuru yìí jẹ ẹ̀kọ, tàbí kí wọ́n jẹ ẹ́ lásán.

## 4.5 Èso, Ewébẹ̀ àti àwọn ohun Mímu

Onírúurú èso ni ó wà ní ilẹ̀ Yorùbá, bẹ́ẹ̀ Olódùmarè kẹ́ wọn débi pé bí àsìkò èso kan bá ti ń kásẹ̀ nílẹ̀ ni òmíràn ń yọjú.

Lára àwọn èso pàtàkì tí Ọlọ́run fi jíǹkí àwọn Yorùbá ni ọ̀gẹ̀dẹ̀ wà. Oríṣi ọ̀gẹ̀dẹ̀ méjì ni ó wà, ọ̀gẹ̀dè àgbagbà àti ọ̀gẹ̀dẹ̀ wẹẹrẹ. Oúnjẹ tí a ń rí lára ọ̀gẹ̀dẹ̀ àgbagbà ni bọ̀ọ̀lì, èyí tí a fi iná sun, ìpékeré tía fi epo pupa dín gbẹ, dòdò tí a fi epo pupa gbá. Yàtọ̀ sí èyí, wọ́n tún máa ń fi ọ̀gẹ̀dẹ̀ àgbagbà ṣe èlùbọ́ bẹ́ẹ̀ ni èlùbọ́ ọ̀gẹ̀dẹ̀ yìí máa ń jọ ti èlùbọ iṣu, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń ro òun náà ní àmàlà. Ní ti ọ̀gẹ̀dẹ̀ wẹẹrẹ, wọ́n máa ń jẹ ẹ́ bí ó bá ti pọ́n, tí ó sì ti dẹ̀ láti jẹ.

Àwọn èso mìíràn tí wọ́n tún gbajúmọ̀ ni òrombó, obì, ọsàn àgbálùmọ̀, orógbó, ọsàn wẹ́wẹ́, ìgbá, mọ́ńgòrò, awùsá, òro, àgbọn, ìbẹ́pẹ, ọ̀pẹ̀ òyìnbó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Gbogbo àwọn èso wọ̀nyí ni wọ́n dára fún ìlera, bẹ́ẹ̀ ni àwọn dọ́kítà Òyìnbó máa ń fún àwọn ènìyàn ní ìmọ̀ràn láti máa jẹ wọ́n déédéé.

Bí a bá ṣe àkíyèsí, a óò rí i pé àwọn Yorùbá máa ń fi àwọn ewébẹ̀ jẹ ọ̀wẹ. Ó lè jẹ́ iyán, àmàlà, ẹ̀bà tàbí fùfú. Àwọn ewébẹ̀ tí Yorùbá máa ń fi jẹun wọ̀nyí ni ilá, ewédú tàbí ọ́ọ́yọ́ àti àwọn ẹ̀fọ́ lóríṣiríṣi. Bí àpẹẹrẹ, tẹ̀tẹ̀, ṣọkọyọ̀kọ̀tọ̀, gbúre, òdú, ewúro, ẹ̀gúsí, amúnútutù, wọ̀ọ̀rọ̀wọ́, yánrin, ìgbàgbá àti ìṣápá, elégédé, olúọrán, olúbèje, ewúrẹ́ orí ìgànná àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ní ìparí, a kò ní í sàìmẹ́nuba àṣà nǹkan mímu tí Yorùbá gbàgbọ́ pé ó ń múwàgún. Lára àwọn ọtí Yorùbá ni ẹmu, ògùrọ̀, bùrùkùtù, àgàdàǹgídí, ọtíkà, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kò ṣe é ṣe láti mẹ́nuba gbogbo ẹ̀ka àṣà Yorùbá nínú àkọsílẹ̀ tàbí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ báyìí, a rí ì pé a ṣe àlàyé àwọn ẹ̀ka àṣà Yorùbá díẹ̀ níbí.

Nínú ìpín yìí ni a tí wo àṣà oúnjẹ jíjẹ àti irúfẹ́ ohun tí wọ́n ń jẹ láyé àtijọ́ di àkókò yìí. A sọ̀rọ̀ lórí oríṣi iṣu tí àwọn Yorùbá máa ń gbìn àti ìwúlò wọn. A kò sàìmẹ́nuba ọ̀gbin ẹ̀gẹ́ àti àwọn oúnjẹ tí ó ń ti ara gbágùdá jáde. Ọ̀gbìn Àgbàdo náà kò gbẹ́yìn àti bí àwọn babańlá wa ṣe ń gbìn ín lẹ́ẹ̀mejì lọ́dún.

Nínú ìpín yìí náà ni a ti sọ̀rọ̀ lórí ẹ̀wà ní onírúurú wọn. A wo ìwúlò ẹ̀wà nínú àgọ́ ara ènìyàn àti ìdí tí àwọn dọ́kítà Òyìnbó ṣe máa ń gbà wá ní ìmọ̀ràn láti máa jẹ ẹ̀wà àti àwọn oúnjẹ mìíràn fún ìdàgbàsókè àti ìlera ara wa. Ní ìparí, a sọ̀rọ̀ lórí àwọn oríṣiríṣi ewébẹ̀ tí Yorùbá ń gbìn láti máa jẹ àwọn oúnjẹ ọlọ́bẹ̀ wa. A kò ṣàìwo oríṣi àwọn ohun mímu tí Yorùbá fi máa ń ṣe ayẹyẹ àti ìgbádùn ara wọn láyé ọjọ́un.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Sọ̀rọ̀ lórí àwọn oúnjẹ ìbílẹ̀ Yorùbá àti ìwúlò wọn.
2. Kín ni pàtàkì iṣukọ ní àwùjọ Yorùbá?
3. Àyípadà wo ni o rò pé ó ti dé bá oúnjẹ Yorùbá ní àsìkò tiwa?
4. Dárúkọ àwọn oúnjẹ kan tí ó ní májèlé.
5. Kín ni ìyàtọ̀ àti ìjọra tí ó wà láàrín Ẹmu àti Ògùrọ̀?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Segun, M. (2007). *RHAPSODY: A Celebration of Nigerian Cooking and Food Culture*, Lagos, Maballine Publications.

Ọyádèjì, B. (1990). *"Orísirísi oúnjẹ tí a ń fi irè oko ṣe"* in *Fèyíkọ́gbọ́n, Vol. 21. Nọ 2.*

Dáramọ́lá, O. & Jẹ́jẹ́, A. (2014). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọn-Òjé Press.

Ologundudu, D. (2008). *The Gaddle of Yorùbá Culture*, U.S., Center for Spoken Words/Institute of Yorùbá Culture.